# الإسلام - نبذة موجزة عن الإسلام

# (مشتملة على الأدلة) (للجمعية)

# Ẹsin Isilaamu

# Ẹsin Isilaamu

## Eleyii ni akọsilẹ soki kan nipa ẹsin Isilaamu gẹgẹ bi o ṣe wa ninu Alikuraani alapọnle pẹlu Sunnah Anọbi

Tira pataki to ko alaye nipa ẹsin Isilaamu sinu, to nṣalaye eyi ti o pataki ju ninu awọn ìpìlẹ, ẹkọ ati awọn ẹwa rẹ lati inu awọn iwe-ẹri ipile; eyi tii ṣẹ Alikuraani alapọnle ati Sunnah Anọbi. Tira yii eyi ti a fi nba gbogbo ẹniti o ti balaga sọrọ, yala o jẹ musulumi tabi kii tiẹṣe musulumi, to si wa ni ede onikaluku wọn, ko le baa wulo ni gbogbo asiko, aaye ati oniruuru iṣesi tabi ipo ti wọn ba wa.

Ẹda kan niyi ti o ko awọn ẹri lati inu Alikurani ati Sunnah Anọbi sinu

## 1. Ẹsin Isilaamu ni iṣẹ naa ti Allah fi ranṣẹ si gbogbo eniyan. Paapaajulọ Oun ni iṣẹ ayeraye ti o sijẹ opin awọn iransẹ Oluwa Allah

Ẹsin Isilaamu ni lẹta Allah si gbogbo eniyan patapata. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{ وَمَآ أَرۡسَلۡنَٰكَ إِلَّا كَآفَّةٗ لِّلنَّاسِ بَشِيرٗا وَنَذِيرٗا وَلَٰكِنَّ أَكۡثَرَ ٱلنَّاسِ لَا يَعۡلَمُونَ}

A ò rán ọ nísẹ́ àfi sí gbogbo ènìyàn pátápátá; (o jẹ́) oníròó-ìdùnnú àti olùkìlọ̀ ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn kò mọ̀. Suratu Sabai: 28 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ قُلْ يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِنِّي رَسُولُ اللَّهِ إِلَيْكُمْ جَمِيعًا}

Irẹ Anọbi sọ pe mo pe ẹyin eniyan (ki ẹ mọ wipe) dajudaju Emi ni iransẹ Allah si gbogbo yin patapata Suratul A'raf: 158 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ قَدْ جَاءَكُمُ الرَّسُولُ بِالْحَقِّ مِن رَّبِّكُمْ فَآمِنُوا خَيْرًا لَّكُمْ ۚ وَإِن تَكْفُرُوا فَإِنَّ لِلَّهِ مَا فِي السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ ۚ وَكَانَ اللَّهُ عَلِيمًا حَكِيمًا}

Ẹyin ènìyàn, dájúdájú Òjíṣẹ́ náà ti dé ba yín pẹ̀lú òdodo láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín. Nítorí náà, kí ẹ gbà á gbọ́ l’ó dára jùlọ fun yín. Tí ẹ bá sì ṣàì gbàgbọ́, dájúdájú ti Allāhu ni ohunkóhun t’ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Allāhu sì ń jẹ́ Onímọ̀, Ọlọ́gbọ́n. Suratu Nisai: 170

Ẹsin Isilaamu ni ifiranṣẹ Allah ti o jẹ ti ayeraye, Oun naa ni igbeyin awọn ifiranṣẹ Oluwa wa. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{مَّا كَانَ مُحَمَّدٌ أَبَا أَحَدٍ مِّن رِّجَالِكُمْ وَلَٰكِن رَّسُولَ اللَّهِ وَخَاتَمَ النَّبِيِّينَ ۗ وَكَانَ اللَّهُ بِكُلِّ شَيْءٍ عَلِيمًا}

(Ànábì) Muhammad kì í ṣe bàbá ẹnì kan kan nínú àwọn ọkùnrin yín, ṣùgbọ́n (ó jẹ́) Òjíṣẹ́ Allāhu àti òpin àwọn Ànábì. Allāhu sì ń jẹ́ Onímọ̀ nípa gbogbo ǹǹkan. Suratul Ahzab: 40

## 2. Ẹsin Isilaamu kii ṣe ẹsin adayanri fun awọn ẹya tabi awọn ijọ kan pato. Ṣugbọn O jẹẹsin Allah fun gbogbo eniyan patapata

Ẹsin Isilaamu kiiṣe ẹsin adayanri fun awọn ẹya tabi awọn ijọ kan pato. Ṣugbọn O jẹẹsin Allah fun gbogbo eniyan patapata. Akọkọ aṣẹ ti Allah pa ninu Alikuraani alapọnle ni gbolohun Rẹ ti ọla Rẹ ga julọ to sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ اعْبُدُوا رَبَّكُمُ الَّذِي خَلَقَكُمْ وَالَّذِينَ مِن قَبْلِكُمْ لَعَلَّكُمْ تَتَّقُونَ}

Ẹyin ènìyàn, ẹ jọ́sìn fún Olúwa yín, Ẹni tí Ó da ẹ̀yin àti àwọn t'ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè ṣọ́ra (fún ìyà Iná). Suratul Baqara: 21 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ اتَّقُوا رَبَّكُمُ الَّذِي خَلَقَكُم مِّن نَّفْسٍ وَاحِدَةٍ وَخَلَقَ مِنْهَا زَوْجَهَا وَبَثَّ مِنْهُمَا رِجَالًا كَثِيرًا وَنِسَاءً }

Mo pe gbogbo ẹyin eniyan, ẹ paya Oluwa yin Ẹni ti O da yin lati ara ẹmi kan ṣoṣo, ti O si tun da iyawo rẹ lati ara rẹ, ti O wa mu jade ni yanturu lati ara awọn mejeeji ọpọlọpọ ọkunrin ati obinrin Suratu Nisai: 1 Egbawa ọrọ wa lati ẹnu Ibnu Umar ki Allah yọnu si awọn mejeeji pe Anọbi- ki ikẹ ati ola Allah maa ba a-ba awọn eeyan sọrọ lọjọ ti o ṣi ilu Makkah, O sọ pe:

«يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِنَّ اللَّهَ قَدْ أَذْهَبَ عَنْكُمْ عُبِّيَّةَ الجَاهِلِيَّةِ وَتَعَاظُمَهَا بِآبَائِهَا فَالنَّاسُ رَجُلَانِ: بَرٌّ تَقِيٌّ كَرِيمٌ عَلَى اللَّهِ وَفَاجِرٌ شَقِيٌّ هَيِّنٌ عَلَى اللَّهِ وَالنَّاسُ بَنُو آدَمَ وَخَلَقَ اللَّهُ آدَمَ مِنْ تُرَابٍ قال الله:{يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِنَّا خَلَقْنَاكُم مِّن ذَكَرٍ وَأُنثَىٰ وَجَعَلْنَاكُمْ شُعُوبًا وَقَبَائِلَ لِتَعَارَفُوا ۚ إِنَّ أَكْرَمَكُمْ عِندَ اللَّهِ أَتْقَاكُمْ ۚ إِنَّ اللَّهَ عَلِيمٌ خَبِيرٌ} [الحجرات:13] »

Mo pe ẹyin eniyan, dajudaju Ọlọhun ti gbe igberaga awọn keferi alaimọkan to ti ṣiwaju ati fifi babanla ṣe iyanran kuro l'ori yin. Leni, gbogbo eniyan jẹ iran meji: ẹniire, olupaya Ọlọhun ti yoo jẹ alapọnle lọdọ Allah, ati obilẹjẹ eniyan, oloriburuku ti yoo jẹẹni-yẹpẹrẹ lọdọỌlọhun. Gbogbo eniyan jẹ arọmọdọmọ Aadamo, bẹẹỌlọhun si da Aadama latara erupẹ. Allah sọ pe: { Mo pe gbogbo ẹyin eniyan, dajudaju Awa ni A da'yin l'ọkunrin l'obinrin, bẹẹ nii a si ṣe yin ni iran-iran ati idile-idile ki ẹ le fi maa da ara yin mọ. Dajudaju alapọnle eniyan julọ laarin yin ni ẹni naa ti o ba npaya

Ọlọhun julọ. Dajudaju Ọlọhun ni Onimimọ julọ Oloye julọ.} [Suratul Hujuraat: 13] Tirimidhi lo gbaa wa, nọmba (3270) O o lee ri ofin kan to nṣe adayanri awọn eeyan kan tabi awọn ijọ kan latara wiwo iran wọn tabi ijọ wọn tabi ẹya won, yala ninu awọn ofin Alikuraani alapọnle tabi awọn aṣẹ Anọbi alapọnle (ki ikẹ ati ola Allah maa ba a).

## 3. Isilaamu ni ifiranṣẹ Allah, eyi ti O wa lati pe awọn iṣẹ awọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ to ti kọja, eyi ti O fi ran wọn si awọn ijọ wọn, ki ikẹ ati ola Allah maa ba awọn ojiṣẹ Ọlọhun wọnyii.

Isilaamu ni ifiranṣẹ Allah, eyi ti O wa lati pe awọn iṣẹ awọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ to ti kọja, eyi ti O fi ran wọn si awọn ijọ wọn, ki ikẹ ati ola Allah maa ba awọn ojiṣẹỌlọhun wọnyii. Olohun ti ola Re ga so pe:

{ إِنَّا أَوْحَيْنَا إِلَيْكَ كَمَا أَوْحَيْنَا إِلَىٰ نُوحٍ وَالنَّبِيِّينَ مِن بَعْدِهِ ۚ وَأَوْحَيْنَا إِلَىٰ إِبْرَاهِيمَ وَإِسْمَاعِيلَ وَإِسْحَاقَ وَيَعْقُوبَ وَالْأَسْبَاطِ وَعِيسَىٰ وَأَيُّوبَ وَيُونُسَ وَهَارُونَ وَسُلَيْمَانَ ۚ وَآتَيْنَا دَاوُودَ زَبُورًا}

{ Dájúdájú Àwa (fi ìmísí)ránṣẹ́ sí ọ gẹ́gẹ́ bí A ṣe fi ránṣẹ́ sí (Ànábì) Nūh àti àwọn Ànábì (mìíràn) lẹ́yìn rẹ̀. A fi ìmísí ránṣẹ́ sí (àwọn Ànábì) ’Ibrọ̄hīm, ’Ismọ̄‘īl, ’Ishāƙ, Ya‘ƙūb àti àwọn àrọ́mọdọ́mọ (rẹ̀), àti (Ànábì) ‘Īsā, ’Ayyūb, Yūnus, Hārūn àti Sulaemọ̄n. A sì fún (Ànábì) Dāwūd ní Zabūr.} [Suratul Nisai: 163] Ẹsin yii ti Ọlọhun fun Ojiṣẹ Nla Muhammad- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- ni imisi rẹ, Oun naa ni ẹsin ti Ọlọhun

Ọba ṣe ni ilana ẹsin fun awọn Anọbi ti won ti kọja, ti O si pa'wọn lasẹ rẹ. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{شَرَعَ لَكُم مِّنَ الدِّينِ مَا وَصَّىٰ بِهِ نُوحًا وَالَّذِي أَوْحَيْنَا إِلَيْكَ وَمَا وَصَّيْنَا بِهِ إِبْرَاهِيمَ وَمُوسَىٰ وَعِيسَىٰ ۖ أَنْ أَقِيمُوا الدِّينَ وَلَا تَتَفَرَّقُوا فِيهِ ۚ كَبُرَ عَلَى الْمُشْرِكِينَ مَا تَدْعُوهُمْ إِلَيْهِ ۚ اللَّهُ يَجْتَبِي إِلَيْهِ مَن يَشَاءُ وَيَهْدِي إِلَيْهِ مَن يُنِيبُ}

{(Allāhu) ṣe ní òfin fun yín nínú ẹ̀sìn (’Islām) ohun tí Ó pa ní àṣẹ fún (Ànábì) Nūh àti èyí tí Ó fi ránṣẹ́ sí ọ, àti ohun tí A pa láṣẹ fún (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm, (Ànábì) Mūsā àti (Ànábì) ‘Īsā pé kí ẹ gbé ẹ̀sìn náà dúró. Kí ẹ sì má ṣe pín sí ìjọ̀ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nínú rẹ̀. Wàhálà l’ó jẹ́ fún àwọn ọ̀ṣẹbọ nípa ǹǹkan tí ò ń pè wọ́n sí (níbi mímú Allāhu ní ọ̀kan ṣoṣo). Allāhu l’Ó ń ṣẹ̀ṣà ẹni tí Ó bá fẹ́ sínú ẹ̀sìn Rẹ̀ (tí ò ń pè wọ́n sí). Ó sì ń fi ọ̀nà mọẹni tí ó bá ń ṣẹ́rí padà sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ (nípasẹ̀ ìronúpìwàdà).} Suratu Shura: 13 Eleyii ti Ọlọhun fún Ojiṣẹ Nla Muhammad- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- ni imisi rẹ jẹ ajẹri fun awọn tira Ọlọhun to ti kọja gẹgẹ bii Taoreta ati Injila ko too di pe madaru wọnu awọn mejeeji. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{وَالَّذِي أَوْحَيْنَا إِلَيْكَ مِنَ الْكِتَابِ هُوَ الْحَقُّ مُصَدِّقًا لِّمَا بَيْنَ يَدَيْهِ ۗ إِنَّ اللَّهَ بِعِبَادِهِ لَخَبِيرٌ بَصِيرٌ }

Ohun tí A fi ránṣẹ́ sí ọ nínú Tírà, òhun ni òdodo tí ó ń fi ohun t’ó jẹ́ òdodo rinlẹ̀ nípa èyí t’ó ṣíwájú rẹ̀. Dájúdájú Allāhu ni Onímọ̀-ìkọ̀kọ̀, Olùríran nípa àwọn ẹrúsìn Rẹ̀. Suratu Fatir: 31

## 4. Gbogbo awọn Anọbi patapata- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba wọn- ẹsin kan

## ṣoṣo ni ẹsin wọn, bo tilẹ jẹ pe ilana iṣẹsin wọn ya lọtọọtọ.

Gbogbo awọn Anọbi patapata ki ikẹ ati aanu Allah maa ba wọn, ẹsin kan ṣoṣo ni ẹsin wọn, bo tilẹ jẹ pe ilana iṣẹsin wọn ya lọtọọtọ. Allah ti ọla Rẹga julọ sọ pe:

{وَأَنزَلْنَا إِلَيْكَ الْكِتَابَ بِالْحَقِّ مُصَدِّقًا لِّمَا بَيْنَ يَدَيْهِ مِنَ الْكِتَابِ وَمُهَيْمِنًا عَلَيْهِ ۖ فَاحْكُم بَيْنَهُم بِمَا أَنزَلَ اللَّهُ ۖ وَلَا تَتَّبِعْ أَهْوَاءَهُمْ عَمَّا جَاءَكَ مِنَ الْحَقِّ ۚ لِكُلٍّ جَعَلْنَا مِنكُمْ شِرْعَةً وَمِنْهَاجًا ۚ وَلَوْ شَاءَ اللَّهُ لَجَعَلَكُمْ أُمَّةً وَاحِدَةً وَلَٰكِن لِّيَبْلُوَكُمْ فِي مَا آتَاكُمْ ۖ فَاسْتَبِقُوا الْخَيْرَاتِ ۚ إِلَى اللَّهِ مَرْجِعُكُمْ جَمِيعًا فَيُنَبِّئُكُم بِمَا كُنتُمْ فِيهِ تَخْتَلِفُونَ }

A sọ Tírà (al-Ƙur’ān) kalẹ̀ fún ọ pẹ̀lú òdodo. Ó ń jẹ́rìí sí èyí t’ó jẹ́ òdodo nínú èyí t’ó ṣíwájú rẹ̀ nínú Tírà. Ó ń wá ààbò fún àwọn òfin inú rẹ̀. Nítorí náà, fi ohun tí Allāhu sọ̀kalẹ̀ dájọ́ láààrin wọn. Má ṣe tẹ̀lé ìfẹ́-inú wọn t’ó yapa sí ohun tí ó dé bá ọ nínú òdodo. Olúkùlùkù nínú yín ni A ti ṣe òfin àti ìlànà fún. Àti pé tí ó bá jẹ́ pé Allāhu bá fẹ́, ìbá ṣe yín ní ìjọ kan ṣoṣo (sínú ’Islām), ṣùgbọ́n nítorí kí Ó lè dan yín wò nínú ohun tí Ó fun yín ni. Nítorí náà, ẹ gbawájú níbi iṣẹ́ rere. Ọ̀dọ̀ Allāhu ni ibùpadàsí gbogbo yín pátápátá. Ó sì máa fun yín ní ìró nípa ohun tí ẹ̀ ń yapa ẹnu sí. Suratul Maidat: 48 Ojise Olohun– ki ike ati ola Olohun maa ba a – so pe:

«أَنَا أَوْلَى النَّاسِ بِعِيسَى ابْنِ مَرْيَمَ فِي الدُّنْيَا وَالْآخِرَةِ وَالْأَنْبِيَاءُ إِخْوَةٌ لِعَلَّاتٍ أُمَّهَاتُهُمْ شَتَّى وَدِينُهُمْ وَاحِدٌ»

Emi gan-an ni mo lẹtọ si Isa ọmọ Maryam julọ laarin awọn eeyan laye ati lọrun. Bẹẹ, apejuwe awọn Anọbi

da gẹgẹ bi awọn ọmọ ọbakan, ti iya wọn yatọ, ṣugbọn ọkan ṣoṣo ni ẹsin wọn. Imam Bukhari lo gbaa wa, nọmba (3443)

## 5. Gẹgẹ bi gbogbo awọn Anọbi: Nuha, Ibrahim, Musa, Sulayman ati Dawuda ṣe pepe, bẹẹ naa ni Isilaamu ṣe pepe si inigbagbọ pe ẹni to njẹ Oluwa ni Allah, Aṣẹda, Olufunilarisiki, Ayeni, Apani, Ọlọla-gongo, Oun naa nii Oludari gbogbo nkan, Oun nikan yii naa ni Alaanu, Onikẹ to ga julọ.

**Gẹgẹ bi gbogbo awọn Anọbi: Nuha, Ibrahim, Musa, Sulayman ati Dawuda ṣe pepe, bẹẹ naa ni Isilaamu ṣe pepe si ninigbagbọ pe ẹni to njẹ Oluwa ni Allah, Aṣẹda, Olufunilarisiki, Ayeni, Apani, Ọlọla-gongo, Oun naa nii Oludari gbogbo nkan, Oun nikan yii naa ni Alaanu, Onikẹ to ga julọ. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:**

Gẹgẹ bi gbogbo awọn Anọbi: Nuha, Ibrahim, Musa, Sulayman ati Dawuda ṣe pepe, bẹẹ naa ni Isilaamu ṣe pepe si ninigbagbọ pe ẹni to njẹ Oluwa ni Allah, Aṣẹda, Olufunilarisiki, Ayeni, Apani, Ọlọla-gongo,

Oun naa nii Oludari gbogbo nkan, Oun nikan yii naa ni Alaanu, Onikẹ to ga julọ. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{ يَا أَيُّهَا النَّاسُ اذْكُرُوا نِعْمَتَ اللَّهِ عَلَيْكُمْ ۚ هَلْ مِنْ خَالِقٍ غَيْرُ اللَّهِ يَرْزُقُكُم مِّنَ السَّمَاءِ وَالْأَرْضِ ۚ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ۖ فَأَنَّىٰ تُؤْفَكُونَ }

Ẹyin ènìyàn, ẹ rántí ìdẹra Allāhu lórí yín. Ǹjẹ́ ẹ̀lẹ́dàá kan yàtọ̀ sí Allāhu tún wà tí ó ń pèsè fun yín láti inú sánmọ̀ àti ilẹ̀? Kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Nítorí náà, báwo ni wọ́n ṣe ń ṣẹ yín lórí kúròníbi òdodo? Suratu Fatir: 3 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{قُلْ مَن يَرْزُقُكُم مِّنَ السَّمَاءِ وَالْأَرْضِ أَمَّن يَمْلِكُ السَّمْعَ وَالْأَبْصَارَ وَمَن يُخْرِجُ الْحَيَّ مِنَ الْمَيِّتِ وَيُخْرِجُ الْمَيِّتَ مِنَ الْحَيِّ وَمَن يُدَبِّرُ الْأَمْرَ ۚ فَسَيَقُولُونَ اللَّهُ ۚ فَقُلْ أَفَلَا تَتَّقُونَ }

Sọ pé: “Ta ni Ó ń pèsè fun yín láti inú sánmọ̀ àti ilẹ̀? Ta ni Ó ní ìkápá lórí ìgbọ́rọ̀ àti ìríran? Ta ni Ó ń mú alààyè jáde láti ara òkú, tí Ó tún ń mú òkú jáde láti ara alààyè? Ta sì ni Ó ń ṣe ètò ọ̀rọ̀ (ẹ̀dá)?” Wọ́n yóò wí pé: "Allāhu" Nígbà náà, sọ pé: "Ṣé ẹ ò níí bẹ̀rù (Rẹ̀) ni?" Suratu Yunusa: 31 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{أَمَّن يَبْدَأُ الْخَلْقَ ثُمَّ يُعِيدُهُ وَمَن يَرْزُقُكُم مِّنَ السَّمَاءِ وَالْأَرْضِ ۗ أَإِلَٰهٌ مَّعَ اللَّهِ ۚ قُلْ هَاتُوا بُرْهَانَكُمْ إِن كُنتُمْ صَادِقِينَ}

(Ṣé ìbọ̀rìṣà l’ó dára jùlọ ni) tàbí (jíjọ́sìn fún) Ẹni tí Ó pilẹ̀ ìṣẹ̀dá ẹ̀dá, lẹ́yìn náà, tí Ó máa dá a padà (lẹ́yìn ikú), tí Ó sì ń pèsè fun yín láti sánmọ̀ àti ilẹ̀? Ṣé ọlọ́hun kan tún wà pẹ̀lú Allāhu ni? Sọ pé: "Ẹ mú ẹ̀rí yín wá tí ẹ bá jẹ́ olódodo." Suratu Naml: 64

Gbogbo awọn Anọbi ati ojiṣẹ pata ni a gbe dide pẹlu iponlogo sisin Allah nikan ṣoṣo. Allah ti ọla Rẹ ga ju sọ pe:

{وَلَقَدۡ بَعَثۡنَا فِي كُلِّ أُمَّةٖ رَّسُولًا أَنِ ٱعۡبُدُواْ ٱللَّهَ وَٱجۡتَنِبُواْ ٱلطَّٰغُوتَۖ فَمِنۡهُم مَّنۡ هَدَى ٱللَّهُ وَمِنۡهُم مَّنۡ حَقَّتۡ عَلَيۡهِ ٱلضَّلَٰلَةُۚ فَسِيرُواْ فِي ٱلۡأَرۡضِ فَٱنظُرُواْ كَيۡفَ كَانَ عَٰقِبَةُ ٱلۡمُكَذِّبِينَ}

Dájúdájú A ti gbé Òjíṣẹ́ dìde nínú ìjọ kọ̀ọ̀kan (láti jíṣẹ́) pé: "Ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Kí ẹ sì jìnnà sí àwọn òrìṣà." Nítorí náà, ó wà nínú wọn, ẹni tí Allāhu tọ́ sí ọ̀nà. Ó sì wà nínú wọn, ẹni tí ìṣìnà kò lé lórí. Nítorí náà, ẹ rìn kiri lórí ilẹ̀, kí ẹ sì wòye sí bí àtubọ̀tán àwọn t'ó pé àwọn Òjíṣẹ́ ní òpùrọ́ ṣe rí? Suratul Nahl: 36 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَمَا أَرْسَلْنَا مِن قَبْلِكَ مِن رَّسُولٍ إِلَّا نُوحِي إِلَيْهِ أَنَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا أَنَا فَاعْبُدُونِ}

A kò rán òjíṣẹ́ kan níṣẹ́ ṣíwájú rẹ àfi kí A fi ìmísí ránṣẹ́ sí i pé: "Dájúdájú kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi (Allāhu). Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Mi." Suratul Anbiyaa: 25 Allah fun wa niro nipa Nuha- ki ikẹ ati igẹ Allah maa ba a- pe Oun naa jiṣẹ pe:

{يَا قَوْمِ اعْبُدُوا اللَّهَ مَا لَكُم مِّنْ إِلَٰهٍ غَيْرُهُ إِنِّي أَخَافُ عَلَيْكُمْ عَذَابَ يَوْمٍ عَظِيمٍ}

"Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ ò ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Dájúdájú mò ń bẹ̀rù ìyà Ọjọ́ Ńlá fun yín." Suratul A'raf: 59 Bẹẹ nii aayo Ọlọhun tii ṣe Ibrahim- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- gẹgẹ bi Allah ṣe fun wa niro nipa rẹ pe o sọ pe:

{وَإِبۡرَٰهِيمَ إِذۡ قَالَ لِقَوۡمِهِ ٱعۡبُدُواْ ٱللَّهَ وَٱتَّقُوهُۖ ذَٰلِكُمۡ خَيۡرٞ لَّكُمۡ إِن كُنتُمۡ تَعۡلَمُونَ}

(Rántí Ànábì) 'Ibrọ̄hīm. Nígbà tí ó sọ fún ìjọ rẹ̀ pé: "Ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Kí ẹ sì páyà Rẹ̀. Ìyẹn lóore jùlọ

fun yín tí ẹ bá mọ̀.” Suratul Ankabut: 16 Anọbi Salihu- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- gẹgẹ bi Allah ṣe sọ nipa rẹ pe o sọ pe:

{قَالَ يَا قَوْمِ اعْبُدُوا اللَّهَ مَا لَكُم مِّنْ إِلَٰهٍ غَيْرُهُ ۖ قَدْ جَاءَتْكُم بَيِّنَةٌ مِّن رَّبِّكُمْ ۖ هَٰذِهِ نَاقَةُ اللَّهِ لَكُمْ آيَةً ۖ فَذَرُوهَا تَأْكُلْ فِي أَرْضِ اللَّهِ ۖ وَلَا تَمَسُّوهَا بِسُوءٍ فَيَأْخُذَكُمْ عَذَابٌ أَلِيمٌ}

Ó sọ pé: "Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ è ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Iṣẹ́ ìyanu kúkú ti dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín; èyí ni abo ràkúnmí Allāhu. (Ó jẹ́) àmì kan fun yín. Nítorí náà, ẹ fi sílẹ̀, kí ó máa jẹ kiri lórí ilẹ̀ Allāhu. Ẹ má ṣe fi ọwọ́ aburú kàn án nítorí kí ìyà ẹlẹ́ta-eléro má baà jẹ yín. Suratul A'raf: 73 Anọbi Shuaib- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- gẹgẹ bi Allah ṣe sọ nipa rẹ pe o sọ pe:

{يَا قَوْمِ اعْبُدُوا اللَّهَ مَا لَكُم مِّنْ إِلَٰهٍ غَيْرُهُ ۖ قَدْ جَاءَتْكُم بَيِّنَةٌ مِّن رَّبِّكُمْ ۖ فَأَوْفُوا الْكَيْلَ وَالْمِيزَانَ وَلَا تَبْخَسُوا النَّاسَ أَشْيَاءَهُمْ وَلَا تُفْسِدُوا فِي الْأَرْضِ بَعْدَ إِصْلَاحِهَا ۚ ذَٰلِكُمْ خَيْرٌ لَّكُمْ إِن كُنتُم مُّؤْمِنِينَ}

"Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ è ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Dájúdájú ẹ̀rí t’ó yanjú ti dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín. Nítorí náà, ẹ wọn kóńgò àti òṣùwọ̀n kún. Ẹ má ṣe dín ǹǹkan àwọn ènìyàn kù. Ẹ sì má ṣe ìbàjẹ́ lórí ilẹ̀ lẹ́yìn àtúnṣe rẹ̀. Ìyẹn sì lóore jùlọ fun yín tí ẹ bá jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo. Suratul A'raf: 85

Ni igba akọkọ ti Ọlọhun ba Anọbi Musa- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- sọrọ, Ọba ti mimọ n bẹ fun sọ fun un pe:

{ وَأَنَا اخْتَرْتُكَ فَاسْتَمِعْ لِمَا يُوحَىٰ (13) إِنَّنِي أَنَا اللَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا أَنَا فَاعْبُدْنِي وَأَقِمِ الصَّلَاةَ لِذِكْرِي (14) }

Àti pé Èmi ṣà ọ́ lẹ́ṣà. Nítorí náà, fi etí sí ohun tí A máa fi ránṣẹ́ sí ọ nínú ìmísí.

Dájúdájú Èmi ni Allāhu. Kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi. Nítorí náà, jọ́sìn fún Mi. Kí o sì kírun fún ìrántí Mi. Suratu Ta-ha: 13-14. Bẹẹ nii Allah sọrọ lẹni ti n fun ni niro nipa Anọbi Musa- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a-, O sọ pe Oun gan-an paapaa fi Ọlọhun wa iṣọ, O sọ pe

{إِنِّي عُذْتُ بِرَبِّي وَرَبِّكُم مِّن كُلِّ مُتَكَبِّرٍ لَّا يُؤْمِنُ بِيَوْمِ الْحِسَابِ}

"Dájúdájú èmi sá di Olúwa mi àti Olúwa yín kúrò lọ́wọ́ gbogbo onígbèéraga, tí kò gba Ọjọ́ ìṣírò-iṣẹ́ gbọ́. Suratu Ghafir: 27 Allah fun wa niro nipa Al-Masiihu- ki ikẹ ati igẹ Allah maa ba a- pe Oun naa so pe:

{ إِنَّ اللَّهَ رَبِّي وَرَبُّكُمْ فَاعْبُدُوهُ ۗ هَٰذَا صِرَاطٌ مُّسْتَقِيمٌ }

Dájúdájú Allāhu ni Olúwa mi àti Olúwa yín. Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Un. Èyí ni ọ̀nà tààrà." Aal Im'raan/51 Allah fun wa niro nipa Al-Masiihu- ki ikẹ ati igẹ Allah maa ba a- pe o so pe:

{ يَا بَنِي إِسْرَائِيلَ اعْبُدُوا اللَّهَ رَبِّي وَرَبَّكُمْ ۖ إِنَّهُ مَن يُشْرِكْ بِاللَّهِ فَقَدْ حَرَّمَ اللَّهُ عَلَيْهِ الْجَنَّةَ وَمَأْوَاهُ النَّارُ ۖ وَمَا لِلظَّالِمِينَ مِنْ أَنصَارٍ }

Mo pe ẹyin ọmọ Israẹli, ẹ maa sin Allah tii ṣe Oluwa mi ati tiyin naa. Dajudaju ẹnikẹni ti o ba mu orogun pọ mọ Ọlọhun dajudaju Ọlọhun ti ṣe Alijannah ni eewọ fun irufẹ ẹni naa, ibugbe rẹ si ni inu Ina ko si ni si oluranlọwọ kankan fun awọn ọṣẹbọ alabosi naa. ( Suratul-Maa'idah : 72)

Koda gan-an paapaa, to fi mọ Taoreta ati Injila, ikanpamọ sisin Ọlọhun nikan ṣoṣo jẹyọ ninu awọn

mejeeji. Ọrọ Anọbi Musa- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- jẹyọ ninu iwe Deuteronomy pe: Gbọ irẹ Isirẹli, Oluwa Ọlọhun wa Oluwa ọkanṣoṣo nii Ikanpamọ ọrọ imọlọhun lọkan jẹyọ ninu iwe Maaku nibi ti Messiah- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- ti nsọ pe: Dajudaju akọkọ ofin ni pe: Gbọ, irẹ Isirẹli, Oluwa Ọlọhun wa Oluwa ọkanṣoṣo nii

Ọlọhun ti ọla ati iyi Rẹ gbọngbọn ṣalaye pe gbogbo awọn Anọbi ni a fi iṣẹ pataki tii ṣe ipepe sibi imọlọhun lọkan ran. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe

{وَلَقَدْ بَعَثْنَا فِي كُلِّ أُمَّةٍ رَّسُولًا أَنِ اعْبُدُوا اللَّهَ وَاجْتَنِبُوا الطَّاغُوتَ ۖ فَمِنْهُم مَّنْ هَدَى اللَّهُ وَمِنْهُم مَّنْ حَقَّتْ عَلَيْهِ الضَّلَالَةُ }

Dájúdájú A ti gbé Òjíṣẹ́ dìde nínú ìjọ kọ̀ọ̀kan (láti jíṣẹ́) pé: “Ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Kí ẹ sì jìnnà sí àwọn òrìṣà.” Nítorí náà, ó wà nínú wọn, ẹni tí Allāhu tọ́ sí ọ̀nà. Ó sì wà nínú wọn, ẹni tí ìṣìnà kò lé lórí. Suratul Nahl: 36 Allah tun sọ pe: Sọ pé: "Ẹ sọ fún mi nípa ǹǹkan tí ẹ̀ ń pè lẹ́yìn Allāhu; ẹ fi wọ́n hàn mí ná, kí ni wọ́n ṣẹ̀dá nínú (ohun t’ó wà lórí) ilẹ̀. Tàbí wọ́n ní ìpín kan (pẹ̀lú Allāhu) nínú (ìṣẹ̀dá) àwọn sánmọ̀? Ẹ mú Tírà kan wá fún mi t’ó ṣíwájú (al-Ḳur’ān) yìí tàbí orípa kan nínú ìmọ̀ tí ẹ bá jẹ́ olódodo." Suratul Ahqaf: 4 Alufa agba Saadi- ki Allah ba ni kẹ ẹ- sọ pe: O jẹ ki a mọ wipe iyan ti awọn ọṣẹbọ nja nipa awọn oriṣa wọn, won o ni ẹri tabi itọka lori rẹ, ṣugbọn wọn kan ngbara le aba irọ lasan, irori to ti kúta ati laakai to ti bajẹ ni i. Ohun ti yoo tọka ailẹṣẹ nlẹ rẹ fun Ọ naa ni nigba ti a ba jọ iṣesi wọn yẹbẹyẹbẹ, ti a tọ gbogbo imọ wọn ati awọn iṣẹ wọn ti a si woye si iṣesi awọn nkan ti wọn nlo igbesi

aye wọn le lori lati maa sin, nje awọn nkan yii se wọn ni anfaani kankan laye tabi lọrun Tayseer Alkareem Almannan: oju-ewe 779

## 6. Ọlọhun Allah ti mimọ n bẹ fun-un ti ọla Rẹ sí ga julọ ni Aṣẹda, Oun naa ni O lẹtọ si ijọsin ni Oun nikan, ati wipe a o gbọdọ sin eyikeyi nnkan miran mọ Ọn.

Ọlọhun ni ẹni naa ti o lẹtọ si ki a maa sin-In ni Oun nikan ti a o gbọdọ si sin ẹlomin mọỌn. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ اعْبُدُوا رَبَّكُمُ الَّذِي خَلَقَكُمْ وَالَّذِينَ مِن قَبْلِكُمْ لَعَلَّكُمْ تَتَّقُونَ (21) الَّذِي جَعَلَ لَكُمُ الْأَرْضَ فِرَاشًا وَالسَّمَاءَ بِنَاءً وَأَنزَلَ مِنَ السَّمَاءِ مَاءً فَأَخْرَجَ بِهِ مِنَ الثَّمَرَاتِ رِزْقًا لَّكُمْ ۖ فَلَا تَجْعَلُوا لِلَّهِ أَندَادًا وَأَنتُمْ تَعْلَمُونَ (22) }

Ẹ̀yin ènìyàn, ẹ jọ́sìn fún Olúwa yín, Ẹni tí Ó da ẹ̀yin àti àwọn t'ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè ṣọ́ra (fún ìyà Iná).

(Ẹ jọ́sìn fún) Ẹni tí Ó ṣe ilẹ̀ fun yín ní ìtẹ́, (Ó ṣe) sánmọ̀ ní àjà, Ó sọ omi òjò kalẹ̀ láti sánmọ̀, Ó sì fi mú àwọn èso jáde ní ìjẹ-ìmu fun yín. Nítorí náà, ẹ má ṣe bá Allāhu wá akẹgbẹ́, ẹ sì mọ̀ (pé kò ní akẹgbẹ́). Suratul Baqarat: 21-22 Ẹni ti O da wa ati awọn iran eniyan to ti kọja, ti O si ṣe ilẹ ni pẹrẹsẹ to tun nsọ omi kalẹ lati sanmọ to si fi nmu oniranran irugbin ti a fi nṣe arisiki jade, Oun nikan naa lo lẹtọ si ijọsin. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{ يَا أَيُّهَا النَّاسُ اذْكُرُوا نِعْمَتَ اللَّهِ عَلَيْكُمْ ۚ هَلْ مِنْ خَالِقٍ غَيْرُ اللَّهِ يَرْزُقُكُم مِّنَ السَّمَاءِ وَالْأَرْضِ ۚ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ۖ فَأَنَّىٰ تُؤْفَكُونَ }

Ẹyin ènìyàn, ẹ rántí ìdẹ̀ra Allāhu lórí yín. Ǹjẹ́ ẹ̀lẹ́dàá kan yàtọ̀ sí Allāhu tún wà tí ó ń pèsè fun yín láti inú sánmọ̀ àti ilẹ̀? Kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Nítorí náà, báwo ni wọ́n ṣe ń ṣẹ yín lórí kúrò níbi òdodo? Suratu Fatir: 3 Ẹni to n da ẹda to si tun n pese ijẹ-imu Oun nikan ṣoṣo lo lẹtọ si ijọsin. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{ ذَٰلِكُمُ اللَّهُ رَبُّكُمْ ۖ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ۖ خَالِقُ كُلِّ شَيْءٍ فَاعْبُدُوهُ ۚ وَهُوَ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ وَكِيلٌ }

Ìyẹn ni Allāhu, Olúwa yín; kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Ẹlẹ́dàá gbogbo n̄ǹkan. Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Un. Òun sì ni Olùṣọ́ lórí gbogbo n̄ǹkan. Suratul An'am: 102

Gbogbo nnkan kinkan ti awọn eniyan ba nsin lẹyin Ọlọhun ko lẹtọ si ijọsin nitori nkan bẹẹ ko nikapa nnkan kan to ṣe deede ọmọnaagun yala ninu sanmọ tabi l'ori ilẹ, bẹẹ nkan kii ṣe amugbalẹgbẹ fun Allah nibi nkankan, kii sii ṣe oluranlọwọ tabi onigbunwọ fun Ọlọhun. Bawo wa ni wọn yoo ṣe wa maa pe nkan mọ Ọlọhun tabi ki won o maa gbe e sipo amugbalẹgbẹ fun-Un. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{قُلِ ادْعُوا الَّذِينَ زَعَمْتُم مِّن دُونِ اللَّهِ ۖ لَا يَمْلِكُونَ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ فِي السَّمَاوَاتِ وَلَا فِي الْأَرْضِ وَمَا لَهُمْ فِيهِمَا مِن شِرْكٍ وَمَا لَهُ مِنْهُم مِّن ظَهِيرٍ }

Sọ pé: “Ẹ pe àwọn tí ẹ sọ pé (wọ́n jẹ́ olúwa) lẹ́yìn Allāhu.” Wọn kò ní ìkápá òdiwọ̀n ọmọ-iná igún nínú sánmọ̀ tàbí nínú ilẹ̀. Wọn kò sì ní ìpín kan nínú méjèèjì. Àti pé kò sí olùrànlọ́wọ́ kan fún Allāhu láààrin wọn. Suratu Sabai: 22

Allah ti mimọ mbẹ fun ti ọla Rẹ sí ga ni Ẹni ti O da gbogbo ẹda, ti O si mu-un jade latara aisi. Dajudaju mimaabẹ awọn nnkan yii jẹ ẹri pataki to ntọka bibẹ Rẹ (Oun Allah), to si ntọka jijẹ oludari ati ilẹtọ si ijọsin Rẹ.

{وَمِنْ آيَاتِهِ أَنْ خَلَقَكُم مِّن تُرَابٍ ثُمَّ إِذَا أَنتُم بَشَرٌ تَنتَشِرُونَ (20) وَمِنْ آيَاتِهِ أَنْ خَلَقَ لَكُم مِّنْ أَنفُسِكُمْ أَزْوَاجًا لِّتَسْكُنُوا إِلَيْهَا وَجَعَلَ بَيْنَكُم مَّوَدَّةً وَرَحْمَةً ۚ إِنَّ فِي ذَٰلِكَ لَآيَاتٍ لِّقَوْمٍ يَتَفَكَّرُونَ (21) وَمِنْ آيَاتِهِ خَلْقُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَاخْتِلَافُ أَلْسِنَتِكُمْ وَأَلْوَانِكُمْ ۚ إِنَّ فِي ذَٰلِكَ لَآيَاتٍ لِّلْعَالِمِينَ (22) وَمِنْ آيَاتِهِ مَنَامُكُم بِاللَّيْلِ وَالنَّهَارِ وَابْتِغَاؤُكُم مِّن فَضْلِهِ ۚ إِنَّ فِي ذَٰلِكَ لَآيَاتٍ لِّقَوْمٍ يَسْمَعُونَ (23) وَمِنْ آيَاتِهِ يُرِيكُمُ الْبَرْقَ خَوْفًا وَطَمَعًا وَيُنَزِّلُ مِنَ السَّمَاءِ مَاءً فَيُحْيِي بِهِ الْأَرْضَ بَعْدَ مَوْتِهَا ۚ إِنَّ فِي ذَٰلِكَ لَآيَاتٍ لِّقَوْمٍ يَعْقِلُونَ (24) وَمِنْ آيَاتِهِ أَن تَقُومَ السَّمَاءُ وَالْأَرْضُ بِأَمْرِهِ ۚ ثُمَّ إِذَا دَعَاكُمْ دَعْوَةً مِّنَ الْأَرْضِ إِذَا أَنتُمْ تَخْرُجُونَ (25) وَلَهُ مَن فِي السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ ۖ كُلٌّ لَّهُ قَانِتُونَ (26) وَهُوَ الَّذِي يَبْدَأُ الْخَلْقَ ثُمَّ يُعِيدُهُ وَهُوَ أَهْوَنُ عَلَيْهِ}

Ó wà nínú àwọn àmì Rẹ̀ pé, Ó ṣẹ̀dá yín láti ara erùpẹ̀. Lẹ́yìn náà, nígbà náà ẹ̀yin di abara tí ẹ̀ ń fọ́nká (lórí ilẹ̀ ayé).

Ó wà nínú àwọn àmì Rẹ̀ pé, Ó ṣẹ̀dá àwọn aya fun yín láti ara yín nítorí kí ẹ lè rí ìfàyàbalẹ̀ lọ́dọ̀ wọn. Ó sì fi ìfẹ́ àti ìkẹ́ sí ààrin yín. Dájúdájú àwọn àmì wà nínú ìyẹn fún ìjọ t'ó láròjinlẹ̀.

Ó wà nínú àwọn àmì Rẹ̀, dídá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ àti ọ̀kan-ò-jọ̀kan àwọn èdè yín àti àwọn àwọ̀ ara yín. Dájúdájú àwọn àmì wà nínú ìyẹn fún àwọn onímọ̀.

Nínú àwọn àmì Rẹ̀ ni oorun yín ní alẹ̀ àti ní ọ̀sán àti wíwá tí ẹ̀ ń wá nínú oore Rẹ̀ (fún ìjẹ-ìmu). Dájúdájú àwọn àmì wà nínú ìyẹn fún ìjọ t'ó ń gbọ́rọ̀.

Nínú àwọn àmì Rẹ̀ tún ni fífi mọ̀nàmọ́ná hàn yín ní ti ẹ̀rù àti ìrètí. Ó sì ń sọ omi kalẹ̀ láti sánmọ̀. Ó ń fi ta ilẹ̀ jí lẹ́yìn tí ilẹ̀ ti kú. Dájúdájú àwọn àmì wà nínú ìyẹn fún ìjọ t'ó ń ṣe làákàyè.

Àti pé nínú àwọn àmì Rẹ̀ ni pé sánmọ̀ àti ilẹ̀ dúró pẹ̀lú àṣẹ Rẹ̀. Lẹ́yìn náà, nígbà tí Ó bá pè yín ní ìpè kan nígbà náà ni ẹ̀yin yóò máa jáde láti inú ilẹ̀.

TiRẹ̀ ni àwọn t'ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Ẹnì kọ̀ọ̀kan ni olùtẹ̀lé-àṣẹ Rẹ̀.

Oun (Allah) yii naa ni Ẹni naa ti O pilẹ iṣẹda bẹẹ ti yoo si tun da a pada (lẹyin igba ti wọn ba ti ku ti wọn parẹ mọlẹ) koda dida wọn pada rọrun fun-un pupọ ju bibẹrẹ iṣẹda gan-an lọ Suratu Rum: 20-27

Namuruusu jiyan nipa bibẹ Oluwa Rẹ, ni Anọbi Ibrahim- ki ikẹ ati igẹ Allah maa ba a- gẹgẹ bi Allah ṣe fun wa niro nipa rẹ ba sọ fun-un pe:

{قَالَ إِبْرَاهِيمُ فَإِنَّ اللَّهَ يَأْتِي بِالشَّمْسِ مِنَ الْمَشْرِقِ فَأْتِ بِهَا مِنَ الْمَغْرِبِ فَبُهِتَ الَّذِي كَفَرَ ۗ وَاللَّهُ لَا يَهْدِي الْقَوْمَ الظَّالِمِينَ }

Anọbi Ibrahim si sọ fun-un pe, dajudaju Ọlọhun lo nmu Oorun jade lati ibuyọ rẹ, irẹ mu-un jade lati ibuwọ rẹ, irọ alainigbagbọ yii ba han gbangba, bẹẹ Allah kii fi ọna mọ awọn alabosi eniyan. Suratul Bakarat: 258

Gege bee naa ni Anọbi Ibrahim- ki ikẹ ati igẹ Allah maa ba a- se fi ẹri rinlẹ fun awọn eeyan rẹ pe dajudaju Allah ni Ẹni naa ti O fi ọna mọ oun, Oun ni O n fun oun ni jijẹ ati mimu, to si n fun oun ni alaafia nigba ti oun ba ṣe aarẹ, bẹẹ Oun nikan naa ni O mu oun ṣẹmi ti yoo si mu oun kuro l'ayé (nigba ti asiko ba to) O sọ pe:

{الَّذِي خَلَقَنِي فَهُوَ يَهْدِينِ (78) وَالَّذِي هُوَ يُطْعِمُنِي وَيَسْقِينِ (79) وَإِذَا مَرِضْتُ فَهُوَ يَشْفِينِ (80) وَالَّذِي يُمِيتُنِي ثُمَّ يُحْيِينِ (81) }

(Òun ni) Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá mi. Nítorí náà, Ó máa fi ọ̀nà mọ̀ mí;

Ẹni t'Ó ń fún mi ní jíjẹ, t'Ó ń fún mi ní mímu;

Àti pé nígbà tí ara mi kò bá yá, Òun l'Ó ń wò mí sàn;

Ẹni tí Ó máa pa mí, lẹ́yìn náà, Ó máa sọ mí di alààyè; Suratu shuaraa: 78- 81 Ọlọhun tun sọrọ ni Eni ti n fun ni niro nipa Anọbi Musa- ki ikẹ ati igẹ Allah maa ba a- wipe Oun gan-an ba Faraoh ṣe ifẹrijiyan to si sọ fun-un pe: Oluwa re Oun naa nii

{ الَّذِي أَعْطَىٰ كُلَّ شَيْءٍ خَلْقَهُ ثُمَّ هَدَىٰ}

Ẹni ti O yanju fun gbogbo nkan eto iṣẹda rẹ bẹẹ ti O si fun-un ni ọgbọn atinuda rẹ. Suratu Ta-ha: 50

Ọlọhun wa tẹ gbogbo nnkan to n bẹ ninu sanmọ ati ilẹ loriba fun ọmọniyan, O si fi orişirişi idẹra rọkirika rẹ nitori ki ọmọniyan le maa sin Ọlọhun nikan lai nii ṣe keferi si I. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{أَلَمْ تَرَوْا أَنَّ اللَّهَ سَخَّرَ لَكُم مَّا فِي السَّمَاوَاتِ وَمَا فِي الْأَرْضِ وَأَسْبَغَ عَلَيْكُمْ نِعَمَهُ ظَاهِرَةً وَبَاطِنَةً ۗ وَمِنَ النَّاسِ مَن يُجَادِلُ فِي اللَّهِ بِغَيْرِ عِلْمٍ وَلَا هُدًى وَلَا كِتَابٍ مُّنِيرٍ }

Ṣé ẹ ò rí i pé dájúdájú Allāhu rọ ohunkóhun t'ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ohunkóhun t'ó wà nínú ilẹ̀ fun yín, Ó sì pé àwọn ìkẹ́ Rẹ̀ fun yín ní gban̄gba àti ní kọ̀rọ̀? Ó sì wà nínú àwọn ènìyàn ẹni t'ó ń jiyàn nípa Allāhu láì ní ìmọ̀ (al-Ƙur'ān) àti ìmọ̀nà (nínú sunnah Ànábì s.a.w.) àti tírà (onímọ̀-ẹ̀sìn) t'ó ń tan ìmọ́lẹ̀ (sí ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn). Suratu Lukman: 20 Gẹgẹ bi Allah ṣe tẹ gbogbo nkan

to n bẹ ninu sanmọ ati ilẹ loriba fun ọmọniyan, gẹgẹ bẹẹ naa ni O da a ti O si pese gbogbo nkan ti o le ni bukata si gẹgẹ bi igbọran, iriran ati irọnu ọkan ki o le baa kọ imọ eyi ti yoo ṣee lanfaani ti yoo si tọka Oluwa ati Aṣẹda rẹ si i. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{ وَاللَّهُ أَخْرَجَكُم مِّن بُطُونِ أُمَّهَاتِكُمْ لَا تَعْلَمُونَ شَيْئًا وَجَعَلَ لَكُمُ السَّمْعَ وَالْأَبْصَارَ وَالْأَفْئِدَةَ ۙ لَعَلَّكُمْ تَشْكُرُونَ }

Allāhu l'Ó mu yín jáde láti inú ikùn àwọn ìyá yín nígbà tí ẹ̀yin kò tí ì dá ǹǹkan kan mọ̀. Ó sì ṣe ìgbọ́rọ̀, àwọn ìríran àti àwọn ọkàn fun yín nítorí kí ẹ lè dúpẹ́ (fún Un). Suratu Nahl: 78

Dajudaju Ọlọhun ti mimọ ati giga julọ n bẹ fun ni O da gbogbo awọn agbaye yii, ni O si da ọmọniyan ti O si pese gbogbo nkan to le bukata si gẹgẹ bi awọn orikerike ati okun-ara, bẹẹ naa ni O pese gbogbo awọn nkan ti yoo maa ran-an lọwọ lati lanfaani ṣiṣe ẹsin ati riri orilẹ gbe fun-un, bẹẹ ni O si rọ gbogbo nkan to n bẹ ninu sanmọ ati ilẹ fun-un.

Allah si fi ṣiṣẹda gbogbo awọn eda ti o tobi wọnyii ṣe ẹri to ntọka jijẹ Oludari ati Alamojuto Rẹ, eyi to ntọka si pipondandan mimaa sin-In. Oun (Allah) ti mimọ ati giga julọ n bẹ fun sọ pe:

{قُلْ مَنْ يَرْزُقُكُمْ مِنَ السَّمَاءِ وَالْأَرْضِ أَمَّنْ يَمْلِكُ السَّمْعَ وَالْأَبْصَارَ وَمَنْ يُخْرِجُ الْحَيَّ مِنَ الْمَيِّتِ وَيُخْرِجُ الْمَيِّتَ مِنَ الْحَيِّ وَمَنْ يُدَبِّرُ الْأَمْرَ فَسَيَقُولُونَ اللَّهُ فَقُلْ أَفَلَا تَتَّقُونَ }

Sọ pé: "Ta ni Ó ń pèsè fun yín láti inú sánmọ̀ àti ilẹ̀? Ta ni Ó ní ìkápá lórí ìgbọ́rọ̀ àti ìríran? Ta ni Ó ń mú alààyè jáde láti ara òkú, tí Ó tún ń mú òkú jáde láti ara alààyè? Ta sì ni Ó ń ṣe ètò ọ̀rọ̀ (ẹ̀dá)?" Wọn yóò wí

pé: "Allāhu" Nígbà náà, sọ pé: "Ṣé ẹ ò níí bẹ̀rù (Rẹ̀) ni?" Suratu Yunus: 31 Ọba ododo ti mimọ n bẹ fun-Un tun sọ pe

{قُلْ أَرَأَيْتُمْ مَا تَدْعُونَ مِنْ دُونِ اللَّهِ أَرُونِي مَاذَا خَلَقُوا مِنَ الْأَرْضِ أَمْ لَهُمْ شِرْكٌ فِي السَّمَاوَاتِ ائْتُونِي بِكِتَابٍ مِنْ قَبْلِ هَذَا أَوْ أَثَارَةٍ مِنْ عِلْمٍ إِنْ كُنْتُمْ صَادِقِينَ}

Sọ pé: "Ẹ sọ fún mi nípa ǹǹkan tí ẹ̀ ń pè lẹ́yìn Allāhu; ẹ fi wọ́n hàn mí ná, kí ni wọ́n ṣẹ̀dá nínú (ohun t'ó wà lórí) ilẹ̀. Tàbí wọ́n ní ìpín kan (pẹ̀lú Allāhu) nínú (ìṣẹ̀dá) àwọn sánmọ̀? Ẹ mú Tírà kan wá fún mi t'ó ṣíwájú (al-Ƙur'ān) yìí tàbí orípa kan nínú ìmọ̀ tí ẹ bá jẹ́ olódodo." Suratul Ahqaf: 4 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ خَلَقَ السَّمَاوَاتِ بِغَيْرِ عَمَدٍ تَرَوْنَهَا وَأَلْقَىٰ فِي الْأَرْضِ رَوَاسِيَ أَن تَمِيدَ بِكُمْ وَبَثَّ فِيهَا مِن كُلِّ دَابَّةٍ وَأَنزَلْنَا مِنَ السَّمَاءِ مَاءً فَأَنبَتْنَا فِيهَا مِن كُلِّ زَوْجٍ كَرِيمٍ. هَٰذَا خَلْقُ اللَّهِ فَأَرُونِي مَاذَا خَلَقَ الَّذِينَ مِن دُونِهِ بَلِ الظَّالِمُونَ فِي ضَلَالٍ مُّبِينٍ}

O da sanmọ laini opo kankan gẹgẹ bi ẹyin ṣe n ri i, O si fi awon oke nlanla ti ilẹ ki o ma baa mi tabi yẹ gẹrẹ mọ yin lẹsẹ, O si fọn orişirişi daaba sori rẹ, A si nsọ omi kalẹ lati sanmọ ti a fi nmu oniranran eso didun jade ninu rẹ (ilẹ). Eleyii ni işẹda ti Allah şe, ẹ wa fi han mi eyikeyi nkan ti awọn to yatọ si I da. Too, ọrọ naa ni pe awọn alabosi ti wa l'ori anu to han gbangba Suratu Lukman: 10-11 Ọba ododo ti mimọ n bẹ fun-Un tun sọ pe

{ أَمْ خُلِقُوا مِنْ غَيْرِ شَيْءٍ أَمْ هُمُ الْخَالِقُونَ (35) أَمْ خَلَقُوا السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضَ بَل لَّا يُوقِنُونَ (36) أَمْ عِندَهُمْ خَزَائِنُ رَبِّكَ أَمْ هُمُ الْمُصَيْطِرُونَ (37) }

Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni?

Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀? Rárá o, wọn kò màmọ̀ dájú ni.

Tàbí lọ́dọ̀ wọn ni àwọn àpótí ọrọ̀ Olúwa rẹ wà? Tàbí àwọn ni olùborí? Suratu Tur: 35-37 Onimimọ agba Sa'diy sọ pe: Eleyii gan-an ni fífi ẹri lọlẹ fun wọn labẹ nkankan ti wọn o le ni ọna kankan ju ki wọn o ju ọwọ silẹ fún ododo ọrọ, Lai sí bẹẹ wọn yoo di ẹni ti o tapa si nkan ti o ba laakai ati ẹsin mu. Tafsiri Ibnu Sa'di: oju ewe 816

## 7. Allah ni O da gbogbo nkan to n bẹ ninu Aye yala awọn nkan ti a ri tabi eyi ti a ko ri. Gbogbo nkan to ti yatọ si I (Allah) ni yoo maa jẹẹda kan ninu awọn ẹda Rẹ, O si da sanmọ ati ilẹ ni ijọ mẹfa:

Allah ni O da gbogbo nkan to n bẹ ninu Aye yala awọn nkan ti a ri tabi eyi ti a ko ri. Gbogbo nkan to ti yatọ si I (Allah) ni yoo maa jẹẹda kan ninu awọn ẹda Rẹ, Olohun ti ola Re ga so pe:

{قُلْ مَن رَّبُّ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ قُلِ اللَّهُ ۚ قُلْ أَفَاتَّخَذْتُم مِّن دُونِهِ أَوْلِيَاءَ لَا يَمْلِكُونَ لِأَنفُسِهِمْ نَفْعًا وَلَا ضَرًّا ۚ قُلْ هَلْ يَسْتَوِي الْأَعْمَىٰ وَالْبَصِيرُ أَمْ هَلْ تَسْتَوِي الظُّلُمَاتُ وَالنُّورُ ۗ أَمْ جَعَلُوا لِلَّهِ شُرَكَاءَ خَلَقُوا كَخَلْقِهِ فَتَشَابَهَ الْخَلْقُ عَلَيْهِمْ ۚ قُلِ اللَّهُ خَالِقُ كُلِّ شَيْءٍ وَهُوَ الْوَاحِدُ الْقَهَّارُ }

Sọ pé: “Ta ni Olúwa àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀?” Sọ pé: “Allāhu ni.” Sọ pé: “Ṣé lẹ́yìn Rẹ̀ ni ẹ tún mú àwọn aláfẹ̀yìntì kan, tí wọn kò ní ìkápá oore àti ìnira fún ẹ̀mí ara wọn?” Sọ pé: “Ṣé afọ́jú àti olùríran dọ́gba bí? Tàbí

àwọn òkùnkùn àti ìmọ́lẹ̀ dọ́gba? Tàbí wọ́n yóò fún Allāhu ní àwọn akẹgbẹ́ kan tí àwọn náà dá ẹ̀dá bíi ti ẹ̀dá Rẹ̀, (tó bẹ́ẹ̀ gẹ́) tí ẹ̀dá fi jọra wọn lójú wọn?” Sọ pé: “Allāhu ni Ẹlẹ́dàá gbogbo n̄ǹkan. Òun sì ni Ọ̀kan ṣoṣo, Olùborí. Suratu Ra'd: 16

Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَيَخْلُقُ مَا لَا تَعْلَمُونَ}

{Oun (Allah) a si tun maa da nnkan ti ẹ o mọ} Suratu Nahl: 8

Allah si da sanmọ ati ilẹ ni ọjọ mẹfa. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{هُوَ الَّذِي خَلَقَ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضَ فِي سِتَّةِ أَيَّامٍ ثُمَّ اسْتَوَىٰ عَلَى الْعَرْشِ ۚ يَعْلَمُ مَا يَلِجُ فِي الْأَرْضِ وَمَا يَخْرُجُ مِنْهَا وَمَا يَنزِلُ مِنَ السَّمَاءِ وَمَا يَعْرُجُ فِيهَا ۖ وَهُوَ مَعَكُمْ أَيْنَ مَا كُنتُمْ ۚ وَاللَّهُ بِمَا تَعْمَلُونَ بَصِيرٌ }

Òun ni Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ fún ọjọ́ mẹ́fà. Lẹ́yìn náà, Ó gúnwà sí orí Ìtẹ́-ọlá. Ó mọ n̄ǹkan t’ó ń wọ inú ilẹ̀ àti n̄ǹkan t’ó ń jáde láti inú rẹ̀, àti n̄ǹkan t’ó ń sọ̀kalẹ̀ láti inú sánmọ̀ àti n̄ǹkan t’ó ń gùnkè sínú rẹ̀. Àti pé Ó wà pẹ̀lú yín ní ibikíbi tí ẹ bá wà (pẹ̀lú ìmọ̀ Rẹ̀). Allāhu sì ni Olùríran nípa ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́. Suratul Hadid: 4 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَلَقَدْ خَلَقْنَا السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضَ وَمَا بَيْنَهُمَا فِي سِتَّةِ أَيَّامٍ وَمَا مَسَّنَا مِن لُّغُوبٍ }

Dájúdájú A ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀, ilẹ̀ àti n̄ǹkan tó wà láààrin àwọn méjèèjì fún ọjọ́ mẹ́fà. Kò sì rẹ̀ Wá rárá (ám̀bọ̀sìbọ́sí pé A óò sinmi ní ọjọ́ keje). Suratu Qaf: 38

## 8. Allah ti mimọ ati giga ọla n bẹ fun-Un ko ni igbakeji yala nipa ọla tabi

## işẹda tabi idari tabi ijọsin bo tii wu ko mọ.

Allah ti mimọ ati giga ọla n bẹ fun-Un ni Olukapa gbogbo ọla ti ko ni orogun nibi işẹda tabi ọla tabi idari bo tilẹ wu ki o mọ, Olohun ti ola Re ga so pe:

{قُلْ أَرَأَيْتُم مَّا تَدْعُونَ مِن دُونِ اللَّهِ أَرُونِي مَاذَا خَلَقُوا مِنَ الْأَرْضِ أَمْ لَهُمْ شِرْكٌ فِي السَّمَاوَاتِ ۖ ائْتُونِي بِكِتَابٍ مِّن قَبْلِ هَٰذَا أَوْ أَثَارَةٍ مِّنْ عِلْمٍ إِن كُنتُمْ صَادِقِينَ }

Sọ pé: "Ẹ sọ fún mi nípa ǹǹkan tí ẹ́ ń pè lẹ́yìn Allāhu; ẹ fi wọ́n hàn mí ná, kí ni wọ́n ṣẹ̀dá nínú (ohun t'ó wà lórí) ilẹ̀. Tàbí wọ́n ní ìpín kan (pẹ̀lú Allāhu) nínú (ìṣẹ̀dá) àwọn sánmọ̀? Ẹ mú Tírà kan wá fún mi t'ó ṣíwájú (al-Ƙur'ān) yìí tàbí orípa kan nínú ìmọ̀ tí ẹ bá jẹ́ olódodo." Suratul Ahqaf: 4 Alufa agba Saadi- ki Allah ba ni kẹ ẹ- sọ pe: Itumọ ọrọ yii ni pe, sọ fun awọn ti wọn mu awọn orişa ati ere ti wọn o lagbara kankan lati şe gẹgẹ bii anfaani tabi inira tabi ipani tabi iyeni tabi ijini dide ni orogun fun Allah, sọ fun wọn lati şalaye lilẹ awọn orişa wọn, ati wipe awọn orişa naa ko lẹtọ si nkankan ninu ijọsin, sọ fun wọn pe "ẹ fi eyikeyi nkan ti wọn ba da l'ori ilẹ tabi ninu sanmọ han mi, tabi ti wọn ni ifọwọkun kankan nibi dida sanmọ". Njẹ wọn tilẹ da nkankan ninu sanmọ ati ilẹ bi? Se wọn da oke ni? Nje wọn tilẹ sọ pe ki odo o maa şan? Nje awọn ni wọn fọn awọn ẹranko sori ilẹ? Nje awọn ni wọn tilẹ jẹ ki awọn igi o maa hu jade? Ewo gan-an ni ikunlọwọ wọn n bẹ nibẹ ninu awọn nkan wọnyii? Ko si ikunlọwọ wọn kankan nibẹ gẹgẹ bi awọn funra wọn şe gba bẹẹ ka ma tiẹ tii sọ nipa ijẹri awọn miran. Eleyii gan-an ni ẹri

laakai to muna doko l'ori wipe sisin awọn nkan miran yatọ si Allah, irufẹ ijọsin bẹẹ otubantẹ nii, ko l'ẹsẹ nlẹ.

Lẹyin naa lo tun wa sọ pe koda ko tun si ẹri imisi to n gbe ero ati iṣe wọn lẹyin. Oun (Allah) sọ pe {E mu Tira kan ṣiwaju eleyii wa} Iyẹn ni pe tira ti o njẹri si imorogun pọ mọ Ọlọhun "tabi oripa ẹri to jẹ ti mimọ" ti a jogun lati ọdọ awọn ojiṣẹ to pàṣẹ bẹẹ. Ohun ti a mọ pẹlu ẹri to ntọka si i ni pe wọn o to bẹẹ lati mu u wa lati ọdọ eyikeyi ojiṣẹ Ọlọhun, koda gan-an paapaa a tun nfi ọwọ rẹ sọya to si dani l'oju pe gbogbo ojiṣẹ pata lo n pepe sibi imo Olọhun wọn lọkan ti wọn si n kọ imorogun pọ mọ Ọlọhun fun awọn eeyan. Eleyii gan-an naa nii eyi to tobi ju ninu imọ ti ẹgbawa rẹ wa lati akata wọn. Tafsiri Ibnu Sa'di: oju ewe 779

Allah ti mimọ ati giga ọla n bẹ fún, Oun ni Olukapa gbogbo ọla, ko si igbakeji fun-Un ninu ọla Rẹ. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe:

{ قُلِ اللَّهُمَّ مَالِكَ الْمُلْكِ تُؤْتِي الْمُلْكَ مَن تَشَاءُ وَتَنزِعُ الْمُلْكَ مِمَّن تَشَاءُ وَتُعِزُّ مَن تَشَاءُ وَتُذِلُّ مَن تَشَاءُ ۖ بِيَدِكَ الْخَيْرُ ۖ إِنَّكَ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ قَدِيرٌ }

Sọ pe mo pe Irẹ Ọlọhun Olukapa gbogbo ọla, Irẹ ni O n fi ọla fun ẹni ti o ba wu Ọ, bẹẹ ti O si ma n gba ọla kuro lọwọ ẹni ti o ba wu Ọ, Irẹ lo n gbe iyi fun ẹni ti o ba wu Ọ bẹẹ ti O si ma nrẹ ẹni ti o ba wu Ọ nilẹ, lọwọ Rẹ ni gbogbo oore n bẹ, dajudaju Irẹ ni Alagbara lori gbogbo nnkan. Aal Im'raan/26 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọrọ ti O si nṣalaye pe ti E ni ọla ti o pe nṣe lọjọ Alukiyamọ:

{ يَوْمَ هُم بَارِزُونَ ۖ لَا يَخْفَىٰ عَلَى اللَّهِ مِنْهُمْ شَيْءٌ ۚ لِّمَنِ الْمُلْكُ الْيَوْمَ ۖ لِلَّهِ الْوَاحِدِ الْقَهَّارِ }

Ní ọjọ́ tí wọn yóò yọ jáde (láti inú sàréè), kiní kan kò sì níí pamọ́ nípa wọn fún Allāhu. (Allāhu yó sì sọ pé): "Ti ta ni ìjọba ní ọjọ́ òní? Ti Allāhu, Ọ̀kan ṣoṣo, Olùborí ni." Suratu Ghafir: 16

Allah ti mimọ ati giga ọla n bẹ fun-Un ko ni igbakeji yala nipa ọla tabi iṣẹda tabi idari tabi ijọsin bo tii wu ko mọ, Olohun ti ola Re ga so pe:

{ وَقُلِ الْحَمْدُ لِلَّهِ الَّذِي لَمْ يَتَّخِذْ وَلَدًا وَلَمْ يَكُن لَّهُ شَرِيكٌ فِي الْمُلْكِ وَلَمْ يَكُن لَّهُ وَلِيٌّ مِّنَ الذُّلِّ ۖ وَكَبِّرْهُ تَكْبِيرًا }

Kí o sì sọ pé: "Gbogbo ọpẹ́ ń jẹ́ ti Allāhu, Ẹni tí kò fi ẹnì kan ṣe ọmọ. Kò sì ní akẹgbẹ́ nínú ìjọba. Kò yẹpẹrẹ áḿbọ̀sìbọ́sí pé Ó máa wá bùkátà sí olùrànlọ́wọ́." Gbé títóbi fún Un gan-an. Suratul Israa: 111 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ الَّذِي لَهُ مُلْكُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَلَمْ يَتَّخِذْ وَلَدًا وَلَمْ يَكُن لَّهُ شَرِيكٌ فِي الْمُلْكِ وَخَلَقَ كُلَّ شَيْءٍ فَقَدَّرَهُ تَقْدِيرًا }

(Òun ni) Ẹni tí Ó ni ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Kò mú ẹnì kan kan ní ọmọ. Kò sí akẹgbẹ́ fún Un nínú ìjọba (Rẹ̀). Ó dá gbogbo n̄ǹkan. Ó sì yan òdíwọ̀n (ìrísí, ìṣẹ̀mí àti àyànmọ́) fún un níwọ̀n-níwọ̀n. Suratul Furqan: 2 Oun nikan ni O ni ikapa gbogbo nkan, gbogbo nkan miran yatọ si I si jẹ ẹda ọwọ Rẹ, Oun naa ni O n dari gbogbo iṣesi ati alaamọri. Ẹni ti O ṣe pe bayii ni iroyin Rẹ, Oun gan-an ni o di ọranyan lati maa jọsin fun, bẹẹ jijọsin fun nkan miran yatọ si I jẹ iwa aipe laakai ati imorogun mọ Ọlọhun eleyi ti yoo ba aye ati orun ẹda je. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe

{ وَقَالُوا كُونُوا هُودًا أَوْ نَصَارَىٰ تَهْتَدُوا ۗ قُلْ بَلْ مِلَّةَ إِبْرَاهِيمَ حَنِيفًا ۖ وَمَا كَانَ مِنَ الْمُشْرِكِينَ }

Wọ́n wí pé: “Ẹ jẹ́ yẹhudi tàbí nasara kí ẹ mọ̀nà.” Sọ pé: "Rárá, ẹ̀sìn (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm (lẹ̀sìn), olùdúró-déédé, kò sì sí nínú àwọn ọ̀ṣẹbọ." Suratul Baqarat: 135 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ وَمَنْ أَحْسَنُ دِينًا مِّمَّنْ أَسْلَمَ وَجْهَهُ لِلَّهِ وَهُوَ مُحْسِنٌ وَاتَّبَعَ مِلَّةَ إِبْرَاهِيمَ حَنِيفًا ۗ وَاتَّخَذَ اللَّهُ إِبْرَاهِيمَ خَلِيلًا}

Ta l’ó dára ní ẹ̀sìn ju ẹni tí ó jura rẹ̀ sílẹ̀ fún Allāhu, olùṣe-rere sì tún ni, ó tún tẹ̀lé ẹ̀sìn (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm, olùdúró-déédé-nínú-’Islām? Allāhu sì mú (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm ní àyànfẹ́. Suratu Nisai: 125 Ọlọhun ododo ti mimọ n bẹ fun Un tun ṣalaye pe ẹnikẹni to ba n tẹle ọna miran yatọ si ilana ẹsin Anọbi Ibrahim aayo Ọlọhun- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba a- pe iru ẹni bẹẹ lo wu'wa agọ si ẹmi ara rẹ. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe: Ta sì ni ó máa kọ ẹ̀sìn (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm sílẹ̀ àfi ẹni tí ó bá gọ ẹ̀mí ara rẹ̀. A kúkú ti ṣà á lẹ́ṣà n’ílé ayé. Dájúdájú ó tún wà nínú àwọn ẹni rere ní ọ̀run. Suratul Baqarat: 130

## 9. Ati pe Alloohu Oba ti mimo n be fun Un, ko bi omo, won ko si bi I, ko si si akegbe ati alafijo Kankan fun Un.

Ati pe Alloohu Oba ti mimo n be fun Un, ko bi omo, won ko si bi I, ko si si akegbe ati alafijo Kankan fun Un, Oba Ododo ti ola Re ga ti mimo si n be fun Un so pe:

{قُلْ هُوَ اللَّهُ أَحَدٌ (1) اللَّهُ الصَّمَدُ (2) لَمْ يَلِدْ وَلَمْ يُولَدْ (3) وَلَمْ يَكُن لَّهُ كُفُوًا أَحَدٌ (4)}

Sọ pé: "Òun ni Allāhu, Ọ̀kan ṣoṣo.

Allāhu ni Aṣíwájú (tí ẹ̀dá ní bùkátà sí, tí Òun kò sì ní bùkátà sí wọn).

Kò bímọ. Wọn kò sì bí I.

Kò sì sí ẹnì kan tí ó jọ Ọ́." Suuratul Ikhlaas: 1-4. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{رَّبُّ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَمَا بَيْنَهُمَا فَاعْبُدْهُ وَاصْطَبِرْ لِعِبَادَتِهِ ۚ هَلْ تَعْلَمُ لَهُ سَمِيًّا}

Olúwa àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ àti ohun tí ń bẹ láààrin àwọn méjèèjì. Nítorí náà, jọ́sìn fún Un, kí ó sì ṣe sùúrù lórí ìjọ́sìn Rẹ̀. Ǹjẹ́ o mọ ẹni tí ó tún ń jẹ́ orúkọ Rẹ̀? Suuratu Maryam: 65. Oba Ododo ti ipo Re gbongbon so pe:

{فَاطِرُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ ۚ جَعَلَ لَكُم مِّنْ أَنفُسِكُمْ أَزْوَاجًا وَمِنَ الْأَنْعَامِ أَزْوَاجًا ۖ يَذْرَؤُكُمْ فِيهِ ۚ لَيْسَ كَمِثْلِهِ شَيْءٌ ۖ وَهُوَ السَّمِيعُ الْبَصِيرُ}

(Òun ni) Olùpilẹ̀ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Ó ṣẹ̀dá àwọn obìnrin fun yín láti ara yín. Ó tún ṣẹ̀dá àwọn abo ẹran-ọ̀sìn láti ara àwọn akọ ẹran-ọ̀sìn. Ó ń mu yín pọ̀ sí i (nípa ìṣẹ̀dá yín ní akọ-abo). Kò sí kiní kan bí irú Rẹ̀. Òun sì ni Olùgbọ́, Olùríran. Suuratu Shuuroh: 11.

## 10. Ati pe Alloohu ti mimo n be fun Un ti ola Re si tun ga O ki n sokale si inu nkankan, ko si ki n di abara si inu nkankan ninu eda Re.

Ati pe Alloohu ti mimo n be fun Un ti ola Re si tun ga O ki n sokale si inu nkankan, ko si ki n di abara si inu nkankan ninu eda Re, ko si di ẹyọkan pelu

nkankan; iyen sele nitori pe dajudaju Alloohu ni Oba adeda, ati pe nkan ti o ba yato si I eda ni, ati pe Oun ni Oba ti yoo seku, ti nkan ti o ba si yato si I yoo pada di titan. Nitori naa Alloohu O ki n sokale si inu nkankan ninu eda Re, ati pe nkankan o le sokale si inu paapa Re, mimo fun Un, ati pe Oba Alloohu ti mimo n be fun Un tobi ju gbogbo nkan lo, O si tun kanka ju gbogbo nkan lo, Oba Alloohu ti ola Re ga sọ ni Ẹni ti n tako eniti o ba n lero wipe Alloohu sokale si inu Al-Masiih (Eesa):

{لَّقَدْ كَفَرَ الَّذِينَ قَالُوا إِنَّ اللَّهَ هُوَ الْمَسِيحُ ابْنُ مَرْيَمَ ۚ قُلْ فَمَن يَمْلِكُ مِنَ اللَّهِ شَيْئًا إِنْ أَرَادَ أَن يُهْلِكَ الْمَسِيحَ ابْنَ مَرْيَمَ وَأُمَّهُ وَمَن فِي الْأَرْضِ جَمِيعًا ۗ وَلِلَّهِ مُلْكُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَمَا بَيْنَهُمَا ۚ يَخْلُقُ مَا يَشَاءُ ۚ وَاللَّهُ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ قَدِيرٌ}

Wọ́n kúkú ti di kèfèrí, àwọn t’ó wí pé: “Dájúdájú Allāhu ni Mọsīh ọmọ Mọryam.” Sọ pé: “Ta sì l’ó ní ìkápá kiní kan lọ́dọ̀ Allāhu tí (Allāhu) bá fẹ́ pa Mọsīh ọmọ Mọryam, àti ìyá rẹ̀ àti àwọn t’ó ń bẹ lórí ilẹ̀ ayé run pátápátá?” Ti Allāhu ni ìjọba àwọn sánmọ̀, ilẹ̀ àti ohunkóhun tí ń bẹ láààrin àwọn méjèèjì. (Allāhu) ń ṣẹ̀dàá ohunkóhun tí Ó bá fẹ́. Allāhu sì ni Alágbára lórí gbogbo ǹǹkan. Suuratul Maaidah: 17. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَلِلَّهِ الْمَشْرِقُ وَالْمَغْرِبُ ۚ فَأَيْنَمَا تُوَلُّوا فَثَمَّ وَجْهُ اللَّهِ ۚ إِنَّ اللَّهَ وَاسِعٌ عَلِيمٌ (115) وَقَالُوا اتَّخَذَ اللَّهُ وَلَدًا ۗ سُبْحَانَهُ ۖ بَل لَّهُ مَا فِي السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ ۖ كُلٌّ لَّهُ قَانِتُونَ (116) بَدِيعُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ ۖ وَإِذَا قَضَىٰ أَمْرًا فَإِنَّمَا يَقُولُ لَهُ كُن فَيَكُونُ (117) }

Ti Allāhu ni ibùyọ òòrùn àti ibùwọ̀ òòrùn. Nítorí náà, ibikíbi tí ẹ bá dojú kọ ibẹ̀ yẹn náà ni ḳiblah Allāhu. Dájúdájú Allāhu ni Olùgbààyè, Onímọ̀.

Wọ́n wí pé: “Allāhu sọ ẹnì kan di ọmọ.” Mímọ́ ni fún Un! Ọ̀rọ̀ kò rí bẹ́ẹ̀, (àmọ́) tiRẹ̀ ni ohunkóhun t’ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Ẹnì kọ̀ọ̀kan sì ni olùtẹ̀lé-àṣẹ Rẹ̀.

Olùpilẹ̀ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ ni (Allāhu). Nígbà tí Ó bá sì pèbùbù kiní kan, Ó kàn máa sọ fún un pé: “Jẹ́ bẹ́ẹ̀.” Ó sì máa jẹ́ bẹ́ẹ̀. Suuratul Baqarah: 115-117. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ وَقَالُوا اتَّخَذَ الرَّحْمَٰنُ وَلَدًا (88) لَّقَدْ جِئْتُمْ شَيْئًا إِدًّا (89) تَكَادُ السَّمَاوَاتُ يَتَفَطَّرْنَ مِنْهُ وَتَنشَقُّ الْأَرْضُ وَتَخِرُّ الْجِبَالُ هَدًّا (90) أَن دَعَوْا لِلرَّحْمَٰنِ وَلَدًا (91) وَمَا يَنبَغِي لِلرَّحْمَٰنِ أَن يَتَّخِذَ وَلَدًا (92) إِن كُلُّ مَن فِي السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ إِلَّا آتِي الرَّحْمَٰنِ عَبْدًا (93) لَّقَدْ أَحْصَاهُمْ وَعَدَّهُمْ عَدًّا (94) وَكُلُّهُمْ آتِيهِ يَوْمَ الْقِيَامَةِ فَرْدًا (95) }

Wọ́n wí pé: "Àjọkẹ́-ayé fi ẹnì kan ṣe ọmọ." (88).

Dájúdájú ẹ ti mú n̄ǹkan aburú wá.

Àwọn sánmọ̀ fẹ́rẹ̀ fàya pẹ́rẹpẹ̀rẹ nítorí rẹ̀, ilẹ̀ fẹ́rẹ̀ fàya pẹ́rẹpẹ̀rẹ, àwọn àpáta sì fẹ́rẹ̀ dà wó lulẹ̀ gbì

fún wí pé wọ́n pe ẹnì kan ní ọmọ Àjọkẹ́-ayé. (91).

Kò sì yẹ fún Àjọkẹ́-ayé láti fi ẹnì kan ṣe ọmọ.

Kò sí ẹnì kan nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ àyàfi kí ó wá bá Àjọkẹ́-ayé ní ipò ẹrúsìn.

Dájúdájú (Allāhu) mọ̀ wọ́n. Ó sì ka òǹkà wọn tààrà.

Gbogbo wọn yó sì wá bá A ní Ọjọ́ Àjíǹde ní ìkọ̀ọ̀kan. Suuratu Maryam: 88-95. Allah tun sọ pe:

{ ٱللَّهُ لَآ إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ٱلۡحَيُّ ٱلۡقَيُّومُۚ لَا تَأۡخُذُهُۥ سِنَةٞ وَلَا نَوۡمٞۚ لَّهُۥ مَا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَمَا فِي ٱلۡأَرۡضِۗ مَن ذَا ٱلَّذِي يَشۡفَعُ عِندَهُۥٓ إِلَّا بِإِذۡنِهِۦۚ يَعۡلَمُ مَا بَيۡنَ أَيۡدِيهِمۡ وَمَا خَلۡفَهُمۡۖ وَلَا يُحِيطُونَ بِشَيۡءٖ مِّنۡ عِلۡمِهِۦٓ إِلَّا بِمَا شَآءَۚ وَسِعَ كُرۡسِيُّهُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَۖ وَلَا يَـُٔودُهُۥ حِفۡظُهُمَاۚ وَهُوَ ٱلۡعَلِيُّ ٱلۡعَظِيمُ}

Allāhu, kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Alààyè, Alámòjúútó-ẹ̀dá. Òògbé kì í ta Á. Àti pé oorun kì í kùn Ún. TiRẹ̀ ni ohunkóhun t'ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ohunkóhun t'ó wà nínú ilẹ̀. Ta ni ẹni tí ó máa ṣìpẹ̀ lọ́dọ̀ Rẹ̀ àfi pẹ̀lú ìyọ̀ǹda Rẹ̀? Ó mọ ohun tí ń bẹ níwájú wọn àti ohun tí ń bẹ lẹ́yìn wọn. Wọn kò sì ní ìmọ̀ àmọ̀tán nípa kiní kan nínú ìmọ̀ Rẹ̀ àfi ohun tí Ó bá fẹ́ (fi mọ̀ wọ́n). Àga Rẹ̀ gbààyè ju àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Ṣíṣọ́ sánmọ̀ àti ilẹ̀ kò sì dá A lágara. Allāhu ga, Ó tóbi. Suuratul Baqorah: 255. Nitori naa, Eni ti O ba ri bayii, ti ẹda Rẹ naa si ri báyìí, bawo ni yoo se wa sokale si ara okan ninu won? Tabi ki o mu un ni omo? Tabi ki o se e ni olujosin fun pelu Re?

## 11. Alloohu ti mimo n be fun Un ti ola Re si tun ga je Aláàánú Onike si awon eru Re, fun idi eyi O ran awon ojise, O si tun so awon tira kale.

Alloohu ti mimo n be fun Un ti ola Re si tun ga ni Alaaanu Onike awon eru Re, ati pe ninu ikẹ Re si awon eru Re ni pe O ran awon ojise si won, O si tun so awon tira kale; lati fi yo won kuro nibi awon okunkun aigbagbo ati imaa se orogun, lo si ibi imole ṣiṣe Ọlọhun lokan ati imọna, Alloohu ti ola Re ga so pe:

{هُوَ الَّذِي يُنَزِّلُ عَلَىٰ عَبْدِهِ آيَاتٍ بَيِّنَاتٍ لِّيُخْرِجَكُم مِّنَ الظُّلُمَاتِ إِلَى النُّورِ ۚ وَإِنَّ اللَّهَ بِكُمْ لَرَءُوفٌ رَّحِيمٌ}

Òun ni Ẹni t'Ó ń sọ àwọn āyah t'ó yanjú kalẹ̀ fún ẹrúsìn Rẹ̀ nítorí kí ó lè mu yín kúrò nínú àwọn òkùnkùn

wá sínú ìmọ́lẹ̀. Dájúdájú Allāhu ni Aláàánú, Àṣàkẹ́-ọ̀run fun yín. Suuratul Hadiid: 9.

Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ وَمَآ أَرۡسَلۡنَٰكَ إِلَّا رَحۡمَةٗ لِّلۡعَٰلَمِينَ }

A kò sì fi iṣẹ́ ìmísí rán ọ bí kò ṣe pé kí o lè jẹ́ ìkẹ́ fún gbogbo ẹ̀dá. Suuratul Anbiyaah: 107. Ati pe Oba Alloohu tun pa anabi Re lase ki o fun awon erusin ni iro wipe Oun ni Oba Alaforijin Onike, nitori naa, Oba Alloohu ti ola Re ga so pe:

{ نَبِّئْ عِبَادِي أَنِّي أَنَا الْغَفُورُ الرَّحِيمُ}

Fún àwọn ẹrúsìn Mi ní ìró pé dájúdájú Èmi ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Suuratul Hijr: 49. Ati pe ninu aanu Re ati ikẹ Re ni pe Oun naa ni O maa n mu inira kuro ti O si maa n so oore kale fun awon eru Re, Oba Alloohu ti ola Re ga so pe:

{ وَإِن يَمْسَسْكَ اللَّهُ بِضُرٍّ فَلَا كَاشِفَ لَهُ إِلَّا هُوَ ۖ وَإِن يُرِدْكَ بِخَيْرٍ فَلَا رَادَّ لِفَضْلِهِ ۚ يُصِيبُ بِهِ مَن يَشَاءُ مِنْ عِبَادِهِ ۚ وَهُوَ الْغَفُورُ الرَّحِيمُ}

Tí Allāhu bá mú ìnira bá ọ, kò sí ẹni tí ó lè mú un kúrò àfi Òun. Tí Ó bá sì gbèrò oore kan pẹ̀lú rẹ, kò sí ẹni tí ó lè dá oore Rẹ̀ padà. Ó ń ṣoore fún ẹni tí Ó bá fẹ́ nínú àwọn ẹrúsìn Rẹ̀. Òun ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Suuratu Yuunus: 107.

## 12. Alloohu Oun ni Oluwa Onikẹ, Oun nikan ni Ẹni tí yóò ṣe iṣiro gbogbo ẹda ni ọjọ igbende nigba ti Yóò gbe gbogbo wọn dide lati inu saare wọn, ti Yíò sí san èèyàn kọọkan ní ẹsan pẹlu

**nkan ti o ba ṣe ninu dáadáa tàbí aidara, ẹnití o ba sì ṣe àwọn iṣẹ olóore ti o si jẹ Mu'mini, idẹkùn gbere n bẹ fún un, ati pe ẹnití o ba ṣe aigbagbo ti o si tun ṣe awọn iṣẹ aburu, iya ti o tobi n bẹ fún un ni ọjọ ìkẹhìn.**

Alloohu Oun ni Oluwa Onikẹ, Oun nikan ni Ẹni tí yíò ṣe iṣiro gbogbo ẹda ni ọjọ igbedide nigba ti Yóò gbe gbogbo dide lati inu saare wọn, ti Yíò sí san èèyàn kọọkan ní ẹsan pẹlu nkan ti o ba ṣe ninu dáadáa tàbí aidara, ẹnití o ba sì ṣe àwọn iṣẹ olóore ti o si jẹ Mu'mini, idẹkùn gbere n bẹ fún un, ati pe ẹni tí o ba ṣe aigbagbo ti o si tun ṣe awọn iṣẹ aburu, iya ti o tobi n bẹ fún un ni ọjọ ìkẹhìn. Ati pe ninu pipe déédéé Ọlọhun ti mimọ n bẹ fún Un ti ọla Rẹ sì tún ga ati ọgbọn Rẹ ati ikẹ Rẹ pẹlu awọn ẹda Rẹ ni wipe O ṣe ayé yìí ni ilé iṣẹ, ti O sí ṣe ilé keji ni nkan ti ẹsan ati iṣiro máa wáyé ni ibẹ; titi ti olusedaadaa o fi gba ẹsan dáadáa rẹ, ti olùṣe aidaa, alabosi ati olukoja àálà o si jẹ ìyá ikọja àálà ati abosi rẹ; ati pe dajudaju àlámọrí yìí awọn ẹmi kan le máa ro wipe ko sunmọ ki o ṣẹlẹ, nitori naa, Ọlọhun ti fi awọn ẹri ti o pọ lelẹ ti wọn tọka sí wipe dajudaju igbedide òdodo ni ko si iyemeji ni inú rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ وَمِنْ آيَاتِهِ أَنَّكَ تَرَى الْأَرْضَ خَاشِعَةً فَإِذَا أَنزَلْنَا عَلَيْهَا الْمَاءَ اهْتَزَّتْ وَرَبَتْ ۚ إِنَّ الَّذِي أَحْيَاهَا لَمُحْيِي الْمَوْتَىٰ ۚ إِنَّهُ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ قَدِيرٌ}

Nínú àwọn àmì Rẹ̀ tún ni pé dájúdájú ìwọ yóò rí ilẹ̀ ní asálẹ̀. Nígbà tí A bá sì sọ omi kalẹ̀ lé e lórí, ó máa rúra wá, ó sì máa ga (fún híhu irúgbìn jáde). Dájúdájú Ẹni tí Ó jí i, Òun mà ni Ẹni tí Ó máa sọ àwọn òkú di alàààyè. Dájúdájú Allāhu ni Alágbára lórí gbogbo ǹǹkan. Suuratun Fussilat: 39. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِن كُنتُمْ فِي رَيْبٍ مِّنَ الْبَعْثِ فَإِنَّا خَلَقْنَاكُم مِّن تُرَابٍ ثُمَّ مِن نُّطْفَةٍ ثُمَّ مِنْ عَلَقَةٍ ثُمَّ مِن مُّضْغَةٍ مُّخَلَّقَةٍ وَغَيْرِ مُخَلَّقَةٍ لِّنُبَيِّنَ لَكُمْ ۚ وَنُقِرُّ فِي الْأَرْحَامِ مَا نَشَاءُ إِلَىٰ أَجَلٍ مُّسَمًّى ثُمَّ نُخْرِجُكُمْ طِفْلًا ثُمَّ لِتَبْلُغُوا أَشُدَّكُمْ ۖ وَمِنكُم مَّن يُتَوَفَّىٰ وَمِنكُم مَّن يُرَدُّ إِلَىٰ أَرْذَلِ الْعُمُرِ لِكَيْلَا يَعْلَمَ مِن بَعْدِ عِلْمٍ شَيْئًا ۚ وَتَرَى الْأَرْضَ هَامِدَةً فَإِذَا أَنزَلْنَا عَلَيْهَا الْمَاءَ اهْتَزَّتْ وَرَبَتْ وَأَنبَتَتْ مِن كُلِّ زَوْجٍ بَهِيجٍ}

Ẹ̀yin ènìyàn, tí ẹ bá wà nínú iyèméjì nípa àjíǹde, dájúdájú Àwa ṣẹ̀dá yín láti inú erùpẹ̀, lẹ́yìn náà láti inú àtọ̀, lẹ́yìn náà láti inú ẹ̀jẹ̀ dídì, lẹ́yìn náà láti inú báàṣí ẹran tí ó pé ní ẹ̀dá àti èyí tí kò pé ní ẹ̀dá nítorí kí A lè ṣàlàyé (agbára Wa) fun yín. A sì ń mú ohun tí A bá fẹ́ dúró sínú àpò ìbímọ títí di gbèdéke àkókò kan. Lẹ́yìn náà, A óò mu yín jáde ní òpóǹló. Lẹ́yìn náà, (ẹ óò máa ṣẹ̀mí lọ) nítorí kí ẹ lè sánn̄gun dópin agbára yín. Ẹni tí ó máa kú (ní kékeré) wà nínú yín. Ó sì wà nínú yín ẹni tí A óò dá (ìṣẹ̀mí) rẹ̀ sí di àsìkò ogbó kùjọ́kùjọ́ nítorí kí ó má lè mọ̀ ǹǹkan kan mọ̀ lẹ́yìn tí ó ti mọ̀ ọ́n. Àti pé o máa rí ilẹ̀ ní gbígbẹ. Nígbà tí A bá sì sọ òjò kalẹ̀ lé e lórí, ó máa yíra padà. Ó máa gbèrú. Ó sì máa mú gbogbo oríṣiríṣi irúgbìn t'ó dára jáde. Suuratul Hajj: 5. Alloohu Oba Ododo so ninu āyah yìí awọn ẹri làákàyè meta ti ntọka sí igbedide, awọn naa ni:

1- Dajudaju ọmọniyan Olohun da a ni igba àkọ́kọ́ lati ara erupẹ, Ẹni tí O da a lati ara erupẹ Oun naa ni Olukapa lati da a pada si aaye nigba ti o ba di erupẹ.

2- Ẹni tí O da eeyan lati ara omi lọ́gbọ́lọ́gbọ́, O kapa lati da ọmọniyan pada si aaye lẹ́yìn iku rẹ.

3- Dajudaju Ẹni tí Ó ye ilẹ̀ pẹ̀lú òjò lẹ́yìn iku rẹ, O ni ikapa lori jiji àwọn eeyan lẹ́yìn iku won, ati pe o wa ninu aaya yii ẹ̀rí ti o tobi lori ikagara Kuraani bá ẹni tí ó bá fẹ́ mú irú rẹ̀ wá. Ati pe bawo ni aaya yii ṣe ko sinu-ti ko si kii ṣe nkan ti o gun- àwọn ẹ̀rí laakaye mẹta ti o han lori ọrọ kan ti o tobi.

Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{يَوْمَ نَطْوِي السَّمَاءَ كَطَيِّ السِّجِلِّ لِلْكُتُبِ ۚ كَمَا بَدَأْنَا أَوَّلَ خَلْقٍ نُّعِيدُهُ ۚ وَعْدًا عَلَيْنَا ۚ إِنَّا كُنَّا فَاعِلِينَ}

(Ọjọ́ náà ni) ọjọ́ tí A máa ká sánmọ̀ bí kíká ewé tírà. Gẹ́gẹ́ bí A ti ṣe bẹ̀rẹ̀ ìṣẹ̀dá ẹ̀dá ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ (ibẹ̀ náà ni) A óò dá a padà sí. (Ó jẹ́) àdéhùn tí A ṣe. Dájúdájú Àwa máa ṣe bẹ́ẹ̀. Suuratul Anbiyaah: 104 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَضَرَبَ لَنَا مَثَلًا وَنَسِيَ خَلْقَهُ ۖ قَالَ مَن يُحْيِي الْعِظَامَ وَهِيَ رَمِيمٌ (78) قُلْ يُحْيِيهَا الَّذِي أَنْشَأَهَا أَوَّلَ مَرَّةٍ وَهُوَ بِكُلِّ خَلْقٍ عَلِيمٌ}

Àti pé ó fi àkàwé lélẹ̀ nípa Wa. Ó sì gbàgbé ìṣẹ̀dá rẹ̀. Ó wí pé: "Ta ni Ó máa sọ egungun di alààyè nígbà tí ó ti kẹfun?"

Sọ pé: "Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá rẹ̀ nígbà àkọ́kọ́ l’Ó máa sọ ọ́ di alààyè. Òun sì ni Onímọ̀ nípa gbogbo ẹ̀dá. Suuratu yāsīn: 78-79. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ أَأَنتُمْ أَشَدُّ خَلْقًا أَمِ السَّمَاءُ ۚ بَنَاهَا (27) رَفَعَ سَمْكَهَا فَسَوَّاهَا (28) وَأَغْطَشَ لَيْلَهَا وَأَخْرَجَ ضُحَاهَا (29) وَالْأَرْضَ بَعْدَ ذَٰلِكَ دَحَاهَا (30) أَخْرَجَ مِنْهَا مَاءَهَا وَمَرْعَاهَا (31) وَالْجِبَالَ أَرْسَاهَا (32) }

Ṣé ẹ̀yin lẹ lágbára jùlọ ní ìṣẹ̀dá ni tàbí sánmọ̀ tí Allāhu mọ?

Allāhu gbé àjà rẹ̀ ga sókè. Ó sì ṣe é ní pípé t'ó gún régé.

Ó ṣe òru rẹ̀ ní dúdú. Ó sì fa ìyálẹ̀ta rẹ̀ yọ jáde.

Àti ilẹ̀, Ó tẹ́ ẹ pẹrẹsẹ lẹ́yìn ìyẹn (30).

Ó mú omi rẹ̀ àti irúgbìn rẹ̀ jáde láti inú rẹ̀.

Àti àwọn àpáta, Ó fi ìdí wọn múlẹ̀ ṣinṣin (32). Suuratun Nāziāt: 27-30. Oba Ododo sí ṣe alaye wipe dajudaju iseda èèyàn ko ni agbara to iseda sanmọ ati ilẹ ati nkan ti o wa laarin mejeeji. Nitori naa, Ẹnití o kapa lati da awon sanmọ ati ilẹ ko lee kagara lati da ọmọnìyàn pada ni eekeji.

## 13. Alloohu ti mimọ n bẹ fún Un ti ola Re Si tun ga da Anobi Ādam lati ara erupẹ, O wa je ki awon aromodomo re o maa po si leyin re. Nitori naa, awọn èèyàn patapata bákan náà ni won ni ipilẹ wọn, ko sì ọlá fún iran kan lori iran kan, ko sì tun sí fún ìjọ kan lori ijọ kan ayaafi pẹlu ìbẹ̀rù

Alloohu

Alloohu ti mimọ n bẹ fún Un ti ola Re Si tún ga da Anobi Ādam lati ara erupẹ, O wa je ki awon

aromodomo re o maa po si leyin re. Nitori naa, awọn ènìyàn patapata bákan náà ni won ni ipilẹ wọn, ko sì ọlá fún iran kan lori iran kan, ko sì tun sí fún ìjọ kan lori ijọ kan ayaafi pẹlu ìbẹrù Alloohu. Alloohu ti ola Rẹ ga sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِنَّا خَلَقْنَاكُم مِّن ذَكَرٍ وَأُنثَىٰ وَجَعَلْنَاكُمْ شُعُوبًا وَقَبَائِلَ لِتَعَارَفُوا ۚ إِنَّ أَكْرَمَكُمْ عِندَ اللَّهِ أَتْقَاكُمْ ۚ إِنَّ اللَّهَ عَلِيمٌ خَبِيرٌ }

Ẹyin ènìyàn, dájúdájú Àwa ṣẹ̀dá yín láti ara ọkùnrin àti obìnrin. A sì ṣe yín ní orílẹ̀-èdè orílẹ̀-èdè àti ìran-ìran nítorí kí ẹ lè dára yín mọ̀. Dájúdájú alápọ̀n-ọ́nlé jùlọ nínú yín lọ́dọ̀ Allāhu ni ẹni t'ó bẹ̀rù (Rẹ̀) jùlọ. Dájúdájú Allāhu ni Onímọ̀, Alámọ̀tán. Suuratul Hujirōt: 13. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَاللَّهُ خَلَقَكُم مِّن تُرَابٍ ثُمَّ مِن نُّطْفَةٍ ثُمَّ جَعَلَكُمْ أَزْوَاجًا ۚ وَمَا تَحْمِلُ مِنْ أُنثَىٰ وَلَا تَضَعُ إِلَّا بِعِلْمِهِ ۚ وَمَا يُعَمَّرُ مِن مُّعَمَّرٍ وَلَا يُنقَصُ مِنْ عُمُرِهِ إِلَّا فِي كِتَابٍ ۚ إِنَّ ذَٰلِكَ عَلَى اللَّهِ يَسِيرٌ }

Allāhu da yín láti ara erùpẹ̀. Lẹ́yìn náà, (Ó tún da yín) láti ara àtọ̀. Lẹ́yìn náà, Ó ṣe yín ní akọ-abo. Obìnrin kan kò níí lóyún, kò sì níí bímọ àfi pẹ̀lú ìmọ̀ Rẹ̀. Àti pé A ò níí fa ẹ̀mí ẹlẹ́mìí-gígùn gùn, A ò sì ní ṣe àdínkù nínú ọjọ́ orí (ẹlòmíìràn), àfi kí ó ti wà nínú tírà kan. Dájúdájú ìyẹn rọrùn fún Allāhu. Suuratu Fātir: 11. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{هُوَ الَّذِي خَلَقَكُم مِّن تُرَابٍ ثُمَّ مِن نُّطْفَةٍ ثُمَّ مِنْ عَلَقَةٍ ثُمَّ يُخْرِجُكُمْ طِفْلًا ثُمَّ لِتَبْلُغُوا أَشُدَّكُمْ ثُمَّ لِتَكُونُوا شُيُوخًا ۚ وَمِنكُم مَّن يُتَوَفَّىٰ مِن قَبْلُ ۖ وَلِتَبْلُغُوا أَجَلًا مُّسَمًّى وَلَعَلَّكُمْ تَعْقِلُونَ }

Òun ni Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá yín láti inú erùpẹ̀, lẹ́yìn náà láti inú àtọ̀, lẹ́yìn náà láti inú ẹ̀jẹ̀ dídì, lẹ́yìn náà Ó mu yín jáde ní òpóǹló. Lẹ́yìn náà, (Ó da yín sí) nítorí kí ẹ

lè sánn̄gun dópin agbára yín. Lẹ́yìn náà (Ó tún da yín sí) nítorí kí ẹ lè di àgbàlágbà. Ó wà nínú yín ẹni tí A óò ti gba ẹ̀mí rẹ̀ ṣíwájú (ipò àgbà). Àti pé (Ó da yín sí) nítorí kí ẹ lè dàgbà dé gbèdéke àkókò kan àti nítorí kí ẹ lè ṣe làákàyè. Suuratu Gāfir: 67. Ati pe Alloohu ti ola Rẹ ga sọ ni Ẹni tí n se alaye wipe dajudaju Oun da Al-Masīh pẹlu aṣẹ wí bẹ́ẹ̀ jẹ bẹẹ, gegebi O se da Ādam pẹlu aṣẹ wí bẹ́ẹ̀ jẹ bẹẹ, Alloohu ti ola Rẹ ga sọ pe:

{ إِنَّ مَثَلَ عِيسَىٰ عِندَ اللَّهِ كَمَثَلِ آدَمَ ۖ خَلَقَهُ مِن تُرَابٍ ثُمَّ قَالَ لَهُ كُن فَيَكُونُ }

Dájúdájú irú ‘Īsā lọ́dọ̀ Allāhu dà bí irú Ādam; (Allāhu) dá a láti ara erùpẹ̀. Lẹ́yìn náà, Ó sọ pé: “Jẹ́ bẹ́ẹ̀.” Ó sì jẹ́ bẹ́ẹ̀. Aal Im’raan/59 Ati pe mo ti so saaju nibi ìpínrọ keji (2) wipe dajudaju Anabi - kí ike ati ola Olohun máa bá a - se alaye wipe dajudaju ọmọnìyàn bákan náà ni won ti ko sì ọlá fún enikan lori ẹnikan ayaafi pẹlu ìbẹ̀rù Alloohu..

## 14. Ati pe gbogbo ọmọ kọọkan ní won bi sí inú adamọ (Esin Islaam).

Ati pe gbogbo ọmọ kọọkan ní won bi sí inú adamọ (Esin Islaam), Alloohu ti ola Rẹ ga sọ pe:

{ فَأَقِمْ وَجْهَكَ لِلدِّينِ حَنِيفًا ۚ فِطْرَتَ اللَّهِ الَّتِي فَطَرَ النَّاسَ عَلَيْهَا ۚ لَا تَبْدِيلَ لِخَلْقِ اللَّهِ ۚ ذَٰلِكَ الدِّينُ الْقَيِّمُ وَلَٰكِنَّ أَكْثَرَ النَّاسِ لَا يَعْلَمُونَ }

Nítorí náà, dojú rẹ kọ ẹ̀sìn náà, (kí o jẹ́) olùdúró-déédé-nínú-ẹ̀sìn, ẹ̀sìn àdámọ́ Allāhu èyí tí Ó dá mọ́ àwọn ènìyàn. Kò sì sí ìyípadà fún ẹ̀dá Allāhu. Ìyẹn ni ẹ̀sìn t’ó fẹsẹ̀rinlẹ̀, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn kò mọ̀. Suuratur Rūm: 30.

Ati pe Al-Haneefiyyah oun ni ilana Anabi Ibraheem Ààyò Olohun - kí ola ko máa bá a - Alloohu ti ola Rẹ ga sọ pe:

{ ثُمَّ أَوْحَيْنَا إِلَيْكَ أَنِ اتَّبِعْ مِلَّةَ إِبْرَاهِيمَ حَنِيفًا ۖ وَمَا كَانَ مِنَ الْمُشْرِكِينَ }

Lẹ́yìn náà, A fi ìmísí ránṣẹ́ sí ọ pé kí o tẹ̀lé ẹ̀sìn (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm, olùdúró-déédé-nínú-ẹ̀sìn. Kò sì wà lára àwọn ọ̀ṣẹbọ. Suuratun Nahl: 123. Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe:

«مَا مِنْ مَوْلُودٍ إِلَّا يُولَدُ عَلَى الفِطْرَةِ فَأَبَوَاهُ يُهَوِّدَانِهِ أَوْ يُنَصِّرَانِهِ أَوْ يُمَجِّسَانِهِ كَمَا تُنْتَجُ البَهِيمَةُ بَهِيمَةً جَمْعَاءَ هَلْ تُحِسُّونَ فِيهَا مِنْ جَدْعَاءَ»

"Ko si ọmọ Kankan ti wọn bi ayaafi ki wọn o bi i si ori adamọ (Esin Islaam), obi re mejeeji ni wọn yóò sọọ di Yahudi, tabi ki wọn o sọọ di Nasorah, tabi ki wọn o sọọ di Majuusiy, gẹgẹ bi ẹranko ṣe maa n bi ẹranko ti gbogbo ẹ̀yà ara rẹ pe, ti e o si nii ri adinku Kankan ni ara rẹ: Leyin náà Abu Uroyrah- ki Olohun ọ yónú sí i - n sọ pé:

{فِطْرَةَ اللَّهِ الَّتِي فَطَرَ النَّاسَ عَلَيْهَالَا تَبْدِيلَ لِخَلْقِ اللَّهِ ذَلِكَ الدِّينُ الْقَيِّمُ وَلَكِنَّ أَكْثَرَ النَّاسِ لَا يَعْلَمُونَ }

ẹ̀sìn àdámọ́ Allāhu èyí tí Ó dá mọ́ àwọn ènìyàn. Kò sì sí ìyípadà fún ẹ̀dá Allāhu. Ìyẹn ni ẹ̀sìn t’ó fẹsẹ̀rinlẹ̀, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn kò mọ̀. Suuratur Rūm: 30. Sohiihu ti Al-Bukhaar 4775 Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe:

«أَلَا إِنَّ رَبِّي أَمَرَنِي أَنْ أُعَلِّمَكُمْ مَا جَهِلْتُمْ مِمَّا عَلَّمَنِي يَوْمِي هَذَا كُلُّ مَالٍ نَحَلْتُهُ عَبْدًا حَلَالٌ وَإِنِّي خَلَقْتُ عِبَادِي حُنَفَاءَ كُلَّهُمْ وَإِنَّهُمْ أَتَتْهُمُ الشَّيَاطِينُ فَاجْتَالَتْهُمْ عَنْ دِينِهِمْ وَحَرَّمَتْ عَلَيْهِمْ مَا أَحْلَلْتُ لَهُمْ وَأَمَرَتْهُمْ أَنْ يُشْرِكُوا بِي مَا لَمْ أُنْزِلْ بِهِ سُلْطَانًا »

"Ẹ tẹti, dajudaju Oluwa mi pa mi ni ase ki n fi mo yin nkan ti é ṣe aimokan nipa re ninu nkan ti O fi mo mi ni òní mi, gbogbo dukia ti Mo ba fi tọrẹ fún ẹrú kan ẹtọ ni fún un, ati pe dajudaju Mo da awon eru Mi ni Musulumi, ni àwọn èṣù ba wa ba won ti won sì mu wọn lọ kuro ninu ẹsin wọn, ti won sì se nkan ti Mo se ni ẹtọ ni eewọ fún wọn, ti won sì tún pa won ni àṣẹ kí wọn o mu nǹkan ti Mi o sọ ẹ̀rí kankan kalẹ fún ni orogun pẹlu Mi. Muslim ni o gba a wa 2865.

## 15. Ko sí ẹnikeni ninu awọn eeyan ti won bi ni ẹlẹṣẹ, tabi eniti n jogun ẹṣẹẹnití ọ yato sí i.:

Ko sí ẹnikeni ninu awọn èniyàn ti won bi ni ẹlẹṣẹ, tabi eniti n jogun ẹṣẹẹni tí ọ yato sí i, ati pe Oba Alloohu ti ola Re ga ti fún wa ní ìró nipa wipe dajudaju Anabi Ādam - kí ola ko máa bá a - nigba ti o yapa àṣẹỌlọhun ti oun pelu iyawo rẹ Awahu sí je ninu èso igi, o ka abamo o si tuuba o si beere aforijin Ọlọhun, Olohun wa fi mo on ki o maa wí awọn gbólóhùn kan ti o daa, o si wí i, Ọlọhun si gba tuuba awọn mejeeji, Olohun ti ola re ga sọ pe:

{وَقُلْنَا يَا آدَمُ اسْكُنْ أَنتَ وَزَوْجُكَ الْجَنَّةَ وَكُلَا مِنْهَا رَغَدًا حَيْثُ شِئْتُمَا وَلَا تَقْرَبَا هَٰذِهِ الشَّجَرَةَ فَتَكُونَا مِنَ الظَّالِمِينَ (35) فَأَزَلَّهُمَا الشَّيْطَانُ عَنْهَا فَأَخْرَجَهُمَا مِمَّا كَانَا فِيهِ ۖ وَقُلْنَا اهْبِطُوا بَعْضُكُمْ لِبَعْضٍ عَدُوٌّ ۖ وَلَكُمْ فِي الْأَرْضِ مُسْتَقَرٌّ وَمَتَاعٌ إِلَىٰ حِينٍ (36) فَتَلَقَّىٰ آدَمُ مِن رَّبِّهِ كَلِمَاتٍ فَتَابَ عَلَيْهِ ۚ إِنَّهُ هُوَ التَّوَّابُ الرَّحِيمُ (37) قُلْنَا اهْبِطُوا مِنْهَا جَمِيعًا ۖ فَإِمَّا يَأْتِيَنَّكُم مِّنِّي هُدًى فَمَن تَبِعَ هُدَايَ فَلَا خَوْفٌ عَلَيْهِمْ وَلَا هُمْ يَحْزَنُونَ (38)}

A sì sọ pé: “Ādam, ìwọ àti ìyàwó rẹ, ẹ máa gbé nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra. Kí ẹ máa jẹ nínú rẹ̀ ní gbẹdẹmukẹ ní ibikíbi tí ẹ bá fẹ́. Kí ẹ sì má ṣe súnmọ́ igi yìí, kí ẹ má baà wà nínú àwọn alábòsí.”

Àmọ́ Èṣù yẹ àwọn méjèèjì lẹ́sẹ̀ kúrò nínú Ọgbà Ìdẹ̀ra, ó sì mú wọn jáde kúrò nínú ibi tí wọ́n wà. A sì sọ pé: "Ẹ sọ̀kalẹ̀, ọ̀tá ní apá kan yín jẹ́ fún apá kan. Ibùgbé àti ǹǹkan ìgbádùn sì ń bẹ fun yín lórí ilẹ̀ fún ìgbà (díẹ̀).”

Lẹ́yìn náà, (Ànábì) Ādam rí àwọn ọ̀rọ̀ kan gbà láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀. Ó sì gba ìronúpìwàdà rẹ̀. Dájúdájú Allāhu, Òun ni Olùgba-ìronúpìwàdà, Àṣàkẹ́-ọ̀run.

A sọ pé : “Gbogbo yín, ẹ sọ̀kalẹ̀ kúrò nínú rẹ̀. Nígbà tí ìmọ̀nà bá dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Mi, ẹni tí ó bá tẹ̀lé ìmọ̀nà Mi, ìpáyà kò níí sí fún wọn. Wọn kò sì níí banújẹ́. Suuratul Baqorah (35-38). Ati pe nigbati Olohun ti gba tuuba Anabi Ādam - kí ola ko máa bá a- won o ka a sì ẹnití o ni ese mo, lati igba yen, aromodomo rẹ o le jogún ẹ̀ṣẹ̀ ti o ti yẹ kuro pẹlu tituubah. Ati pe ipilẹ ni wipe ọmọnìyàn o le ru ẹ̀ṣẹ̀ẹni tí o yato sí i, Olohun ti ola Re ga sọ pe:

{وَلَا تَكْسِبُ كُلُّ نَفْسٍ إِلَّا عَلَيْهَا ۚ وَلَا تَزِرُ وَازِرَةٌ وِزْرَ أُخْرَىٰ ۚ ثُمَّ إِلَىٰ رَبِّكُم مَّرْجِعُكُمْ فَيُنَبِّئُكُم بِمَا كُنتُمْ فِيهِ تَخْتَلِفُونَ }

Ẹ̀mí kan kò sì níí ṣe iṣẹ́ kan àfi fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Ẹlẹ́rù-ẹ̀ṣẹ̀ kan kò sì níí ru ẹ̀ṣẹ̀ ẹlòmíìràn. Lẹ́yìn náà, ọ̀dọ̀ Olúwa yín ni ibùpadàsí yín. Ó sì máa fun yín ní ìró ohun tí ẹ̀ ń yapa ẹnu sí Suuratul Anām: 164.

Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{مَّنِ اهْتَدَىٰ فَإِنَّمَا يَهْتَدِي لِنَفْسِهِ ۖ وَمَن ضَلَّ فَإِنَّمَا يَضِلُّ عَلَيْهَا ۚ وَلَا تَزِرُ وَازِرَةٌ وِزْرَ أُخْرَىٰ ۗ وَمَا كُنَّا مُعَذِّبِينَ حَتَّىٰ نَبْعَثَ رَسُولًا }

Ẹnikẹ́ni t'ó bá mọ̀nà, ó mọ̀nà fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Ẹnikẹ́ni t'ó bá sì ṣìnà, ó ń ṣìnà fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Ẹlẹ́rù-ẹ̀ṣẹ̀ kan kò níí ru ẹ̀ṣẹ̀ ẹlòmíìràn. A ò sì níí jẹ àwọn ẹ̀dá níyà títí A fi máa gbé òjíṣẹ́ kan dìde (sí wọn). Suuratul Isrāi: 15. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَلَا تَزِرُ وَازِرَةٌ وِزْرَ أُخْرَىٰ ۚ وَإِن تَدْعُ مُثْقَلَةٌ إِلَىٰ حِمْلِهَا لَا يُحْمَلْ مِنْهُ شَيْءٌ وَلَوْ كَانَ ذَا قُرْبَىٰ ۗ إِنَّمَا تُنذِرُ الَّذِينَ يَخْشَوْنَ رَبَّهُم بِالْغَيْبِ وَأَقَامُوا الصَّلَاةَ ۚ وَمَن تَزَكَّىٰ فَإِنَّمَا يَتَزَكَّىٰ لِنَفْسِهِ ۚ وَإِلَى اللَّهِ الْمَصِيرُ }

Ẹlẹ́rù ẹ̀ṣẹ̀ kan kò níí ru ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ ẹlòmíìràn. Kódà kí ẹnì kan tí ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ wọ̀ lọ́rùn ké sí (ẹlòmíìràn) fún àbárù ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, wọn kò níí bá a ru kiní kan nínú rẹ̀, ìbáà jẹ́ ìbátan. Àwọn tí ò ń ṣèkìlọ̀ fún ni àwọn t'ó ń páyà Olúwa wọn ní ìkọ̀kọ̀, tí wọ́n sì ń kírun. Ẹni tí ó bá ṣàfọ̀mọ́ (ara rẹ̀ kúrò nínú ìwà ẹ̀ṣẹ̀), ó ṣàfọ̀mọ́ fún ẹ̀mí ara rẹ̀ ni. Ọ̀dọ̀ Allāhu sì ni àbọ̀ ẹ̀dá. Suuratu Fātir: 18.

## 16. Ati pe nǹkan ti a torí rẹ dá àwọn èniyàn naa ni: Jijosin fún Olohun ni Oun nikan:

Ati pe nǹkan ti a torí rẹ dá àwọn èniyàn naa ni: Jijosin fún Olohun ni Oun nikan soso. Olohun ti ola Rẹ ga sọ pe:

{ وَمَا خَلَقْتُ الْجِنَّ وَالْإِنسَ إِلَّا لِيَعْبُدُونِ }

Ati wipe mi o da awọn alijannu ati awọn eeyan (fun nkan miran) bi kii ṣe ki wọn le maa sin Mi Suuratudh Dhāriyāt: 56.

## 17. Islam pon omoniyan le- ati okunrin ati obinrin- o si se agbateru fun un nibi gbogbo iwo re, o si se e ni ẹni tí won o bi leere nípa gbogbo awọn nkan ti o sesa re fúnra rẹ àti àwọn iṣẹ rẹ ati awọn ìwà rẹ, o si tun n dì ru u abajade eyikeyi iṣẹ ti o ba le fi ko inira ba ẹ̀mi ara rẹ tabi ti o le ko inira ba elomiiran.

17. Islam pon omoniyan le- ati okunrin ati obinrin- o si se agbateru fun un nibi gbogbo iwo re, o si se e ni ẹni tí won o bi leere nípa gbogbo awọn nkan ti o sesa re fúnra rẹ àti àwọn iṣẹ rẹ ati awọn ìwà rẹ, o si tun n dì ru u abajade eyikeyi iṣẹ ti o ba le fi ko inira ba ẹ̀mi ara rẹ tabi ti o le ko inira ba elomiiran.

{وَإِذْ قَالَ رَبُّكَ لِلْمَلَائِكَةِ إِنِّي جَاعِلٌ فِي الْأَرْضِ خَلِيفَةً}

(Rántí) nígbà tí Olúwa rẹ sọ fún àwọn mọlāika pé: “Dájúdájú Èmi yóò fi àrólé kan sórí ilẹ̀. Suuratul Baqorah: 30.

Apọnle yìí kò gbogbo ọmọ Anọbi Ādam sinu, Olohun ti ola Rẹ ga sọ pe:

{وَلَقَدْ كَرَّمْنَا بَنِي آدَمَ وَحَمَلْنَاهُمْ فِي الْبَرِّ وَالْبَحْرِ وَرَزَقْنَاهُم مِّنَ الطَّيِّبَاتِ وَفَضَّلْنَاهُمْ عَلَىٰ كَثِيرٍ مِّمَّنْ خَلَقْنَا تَفْضِيلًا}

Dájúdájú A ṣe àpọ́nlé fún àwọn ọmọ (Ànábì) Ādam; A gbé wọn rìn lórí ilẹ̀ àti lórí omi; A fún wọn ní ìjẹ-ìmu nínú àwọn n̄ǹkan dáadáa; A sì ṣoore àjùlọ

fún wọn gan-an lórí ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn tí A dá. Suuratul Isrāi: 70 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{لَقَدْ خَلَقْنَا الْإِنسَانَ فِي أَحْسَنِ تَقْوِيمٍ }

Dájúdájú A ṣẹ̀dá ènìyàn pẹ̀lú ìrísí t'ó dára jùlọ. Suuratur Tīn: 4.

Olohun kọ̀ fún ọmọnìyàn kuro nibi ki o sọ ara re di omoleyin eniyepere fún olùjọsìn fún kan tabi ẹni ti wọn n tẹ̀lé kan, tabi ẹni tí wọ́n n tẹ̀lé àṣẹ rẹ kan leyin Alloohu, Olohun ti ola Rẹ ga sọ pe:

{وَمِنَ النَّاسِ مَن يَتَّخِذُ مِن دُونِ اللَّهِ أَندَادًا يُحِبُّونَهُمْ كَحُبِّ اللَّهِ ۖ وَالَّذِينَ آمَنُوا أَشَدُّ حُبًّا لِّلَّهِ ۗ وَلَوْ يَرَى الَّذِينَ ظَلَمُوا إِذْ يَرَوْنَ الْعَذَابَ أَنَّ الْقُوَّةَ لِلَّهِ جَمِيعًا وَأَنَّ اللَّهَ شَدِيدُ الْعَذَابِ. إِذۡ تَبَرَّأَ ٱلَّذِينَ ٱتُّبِعُواْ مِنَ ٱلَّذِينَ ٱتَّبَعُواْ وَرَأَوُاْ ٱلۡعَذَابَ وَتَقَطَّعَتۡ بِهِمُ ٱلۡأَسۡبَابُ}

Ó sì ń bẹ nínú àwọn ènìyàn, ẹni tí ń jọ́sìn fún àwọn òrìṣà lẹ́yìn Allāhu. Wọ́n nífẹ̀ẹ́ wọn gẹ́gẹ́ bí ìfẹ́ (tó yẹ kí wọ́n ní sí) Allāhu. Àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo sì le jùlọ nínú ìfẹ́ sí Allāhu. Tí ó bá jẹ́ pé àwọn t'ó ṣàbòsí lè rí ìgbà tí wọ́n máa rí Ìyà náà ni, (wọn ìbá mọ̀ pé) dájúdájú gbogbo agbára ń jẹ́ ti Allāhu. Àti pé dájúdájú Allāhu le (níbi) ìyà.(Rántí) nígbà tí àwọn tí wọ́n tẹ̀lé (nínú àìgbàgbọ́) máa yọwọ́ yọsẹ̀ kúrò nínú ọ̀rọ̀ àwọn t'ó tẹ̀lé wọn; (nígbà tí) wọ́n bá fojú rí Ìyà, tí ohun t'ó so wọ́n pọ̀ sì já pátápátá. Suuratul Baqorah: 165-166. Olohun ti ola re ga sọ ti O fi n se alaye isesi awon omoleyin ati awọn ti won n tẹ̀lé pelu ibaje ni ojo igbende pé:

{ قَالَ الَّذِينَ اسْتَكْبَرُوا لِلَّذِينَ اسْتُضْعِفُوا أَنَحْنُ صَدَدْنَاكُمْ عَنِ الْهُدَىٰ بَعْدَ إِذْ جَاءَكُم ۖ بَلْ كُنتُم مُّجْرِمِينَ (32) وَقَالَ الَّذِينَ اسْتُضْعِفُوا لِلَّذِينَ اسْتَكْبَرُوا بَلْ مَكْرُ اللَّيْلِ وَالنَّهَارِ إِذْ تَأْمُرُونَنَا أَن نَّكْفُرَ بِاللَّهِ وَنَجْعَلَ لَهُ أَندَادًا ۚ وَأَسَرُّوا النَّدَامَةَ لَمَّا رَأَوُا

الْعَذَابَ وَجَعَلْنَا الْأَغْلَالَ فِي أَعْنَاقِ الَّذِينَ كَفَرُوا ۚ هَلْ يُجْزَوْنَ إِلَّا مَا كَانُوا يَعْمَلُونَ (33) }

Àwọn t'ó ṣègbéraga yó sì wí fún àwọn tí wọ́n sọ di ọ̀lẹ pé: "Ṣé àwa l'a ṣẹ yín lórí kúrò nínú ìmọ̀nà lẹ́yìn tí ó dé ba yín? Rárá o! Ọ̀daràn ni yín ni."

Àwọn tí wọ́n sọ di ọ̀lẹ yó sì wí fún àwọn t'ó ṣègbéraga pé: "Rárá! Ète òru àti ọ̀sán (láti ọ̀dọ̀ yín lókó bá wa) nígbà tí ẹ̀ ń pa wá ní àṣẹ pé kí á ṣàì gbàgbọ́ nínú Allāhu, kí á sì sọ (àwọn kan) di ẹgbẹ́ Rẹ̀." Wọ́n fi àbámọ̀ wọn pamọ́ nígbà tí wọ́n rí ìyà. A sì kó ẹ̀wọ̀n sí ọrùn àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́. Ṣé A óò san wọ́n ní ẹ̀san kan bí kò ṣe ohun tí wọ́n ń ṣe níṣẹ́? Suuratu Sabai: 32 - 33.

Ati pe ninu pípé deede Olohun ti mimọ n bẹ fún Un ti ola Rẹ sì tún ga ni ojo igbedide ni ki awon olupepe ati awọn asiwaju asọninu o ru awọn ẹsẹ wọn ati awọn ẹsẹ awon ti won ṣì lọ́nà ti ko sì ìmọ fún wọn, Olohun ti ola Rẹ ga sọ pe:

{لِيَحْمِلُوا أَوْزَارَهُمْ كَامِلَةً يَوْمَ الْقِيَامَةِ ۙ وَمِنْ أَوْزَارِ الَّذِينَ يُضِلُّونَهُم بِغَيْرِ عِلْمٍ ۗ أَلَا سَاءَ مَا يَزِرُونَ}

(Wọ́n sọ bẹ́ẹ̀) nítorí kí wọ́n lè ru ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ tiwọn ní pípé pérépéré ní Ọjọ́ Àjíǹde àti (nítorí kí wọ́n lè rù) nínú ẹrù ẹ̀ṣẹ̀ àwọn tí wọ́n ń ṣì lọ́nà pẹ̀lú àìnímọ̀. Gbọ́, ohun tí wọn yóò rù ní ẹ̀ṣẹ̀, ó burú. Suuratun Nahl: 25.

Ati pe Islaam ti se agbateru fún ọmọnìyàn gbogbo iwọ̀ rẹ ní ayé àti ní ọjọ ìkẹhìn, ati pe eyi ti o tobi julọ ninu awọn iwọ̀ ti Islaam se agbateru re ti o si se alaye re fún ọmọnìyàn ni: Iwọ̀ Olohun lori ọmọnìyàn ati iwọ̀ọmọnìyàn lori Olohun

فعَنْ مُعَاذٍ رضي الله عنه قَالَ: أَنَا رَدِيفُ النَّبِيِّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَقَالَ: «يَا مُعَاذُ» قُلْتُ: لَبَّيْكَ وَسَعْدَيْكَ ثُمَّ قَالَ مِثْلَهُ ثَلاَثًا: «هَلْ تَدْرِي مَا حَقُّ اللَّهِ عَلَى العِبَادِ» قُلْتُ: لاَ قَالَ: «حَقُّ اللَّهِ عَلَى العِبَادِ أَنْ يَعْبُدُوهُ وَلاَ يُشْرِكُوا بِهِ شَيْئًا» ثُمَّ سَارَ سَاعَةً فَقَالَ: «يَا مُعَاذُ» قُلْتُ: لَبَّيْكَ وَسَعْدَيْكَ قَالَ: "هَلْ تَدْرِي مَا حَقُّ العِبَادِ عَلَى اللَّهِ إِذَا فَعَلُوا ذَلِكَ: أَنْ لاَ يُعَذِّبَهُمْ »

Nitori naa, won gba wa lati ọdọ Muādh - ki Olohun yonu sí i - o sọpe: Mo wa leyin Anobi - kí ike ati ola Olohun máa bá a - lori nkan ọ̀gùn, o wá so pe: Irẹ Muādh, mo sọ pe: Mo n jẹ ipe rẹ oriire sì ni ti e, leyin náà o so nkan ti o jo bee ni èèmeta: "Ǹjẹ́ o mọ iwọ̀ Olohun lori awon ẹrú?", mo sọ pé: Rárá, o sọ pe: "Iwọ̀ Olohun lori awon eru ni ki won o maa josin fún Un ki wọn o si ma mu nkankan mii mo on ni orogun", leyin náà o rin fun wákàtí kan, ni o wá sọ pe: "Irẹ Muādh", mo sọ pé: Mo n jẹ ipe rẹ oriire sì ni ti e, o sọ pe: Ǹjẹ́ o mo iwọ̀ awon eru lori Olohun ti won ba ti se ìyẹn: Oun naa ni ki O ma fi iya jẹ won". Sọhiihu ti Buhari 6840

Islaam se agbateru fún ọmọnìyàn ẹsin re ti o jẹ ododo ati aromodomo re ati dukia rẹ ati omoluabi rẹ. O sọ– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– pe:

«فَإِنَّ اللَّهَ حَرَّمَ عَلَيْكُمْ دِمَاءَكُمْ وَأَمْوَالَكُمْ وَأَعْرَاضَكُمْ كَحُرْمَةِ يَوْمِكُمْ هَذَا فِي شَهْرِكُمْ هَذَا فِي بَلَدِكُمْ هَذَا»

"Dajudaju Olohun se ni eewọ lẹ yin lori, awon ẹjẹ yín, àti àwọn dukia yin, ati awọn omoluabi yin, gegebi jije eewọọjọ yin yii, ni oṣù yin yii, ni ilu yin yii. Sọhiihu ti Buhari 6501 Ati pe dajudaju Òjíṣẹ̀Ọlọhun - kí ike ati ola Olohun máa bá a - ti Kede adehun ti o tobi yii nibi Hajj idagbere eleyi ti awọn ti won le ni ẹgbẹ̀rún lọna ọgọ́rùn-ún ninu awon saabe gaani rẹ, o si tun paara

itumo yii, o si tun kanpá mọọn ni ọjọ́ ìgúnran ninu Hajj idagbere.

Islaam se ọmọnìyàn ni ẹni tí won o bi leere nípa gbogbo awọn nkan ti o sesa re fúnra rẹ àti àwọn iṣẹ rẹ ati awọn ìwà rẹ, Olohun ti ola Rẹ ga sọ pe:

{ وَكُلَّ إِنسَانٍ أَلْزَمْنَاهُ طَائِرَهُ فِي عُنُقِهِ ۖ وَنُخْرِجُ لَهُ يَوْمَ الْقِيَامَةِ كِتَابًا يَلْقَاهُ مَنشُورًا اقْرَأْ كِتَابَكَ كَفَىٰ بِنَفْسِكَ الْيَوْمَ عَلَيْكَ حَسِيبًا }

Ènìyàn kọ̀ọ̀kan ni A ti la àyànmọ́ àti ìwé iṣẹ́ rẹ̀ bọ̀ lọ́rùn. A sì máa mú ìwé kan jáde fún un ní Ọjọ́ Àjíǹde. Ó máa pàdé rẹ̀ ní ṣíṣí sílẹ̀. Suuratul Isrāi: 13 Iyẹn ni wipe nnkan ti o ba ṣe ninu dáadáa tàbí aburu Ọlọhun a jẹ ki o wa pẹ̀lú rẹ ti ko sì ni tayọ rẹ̀ lọ sí ọdọ ẹni tí o yatọ sí i, nitori naa wọn o nii se isiro rẹ pẹlu iṣẹ ẹnití o yatọ sí i, won o si ni se isiro ẹnití o yatọ sí i pẹlu iṣẹ rẹ. Ọlọhun ti ola Rẹ ga sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الْإِنسَانُ إِنَّكَ كَادِحٌ إِلَىٰ رَبِّكَ كَدْحًا فَمُلَاقِيهِ}

Ìwọ ènìyàn dájúdájú ìwọ ń ṣe iṣẹ́ kárakára ní iṣẹ́ àṣepàdé Olúwa rẹ. O sì máa mú un pàdé Rẹ̀. Suuratul Inshiqōq: 6 Allah tun sọ pe:

{ مَّنْ عَمِلَ صَٰلِحًا فَلِنَفْسِهِۦ ۖ وَمَنْ أَسَآءَ فَعَلَيْهَا ۗ وَمَا رَبُّكَ بِظَلَّٰمٍ لِّلْعَبِيدِ}

Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere, ó ṣe é fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì ṣe aburú, ó ṣe é fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Olúwa rẹ kò sì níí ṣe àbòsí sí àwọn ẹrúsìn. Fussilat:46

Ati pe Islaam n dì ru ọmọnìyàn abajade eyikeyi iṣẹ ti o ba le fi ko inira ba ẹ̀mi ara rẹ tabi ti o le ko inira ba elomiiran, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَمَن يَكْسِبْ إِثْمًا فَإِنَّمَا يَكْسِبُهُ عَلَىٰ نَفْسِهِ ۚ وَكَانَ اللَّهُ عَلِيمًا حَكِيمًا}

Ẹnikẹ́ni tí ó bá dá ẹ̀ṣẹ̀ kan, ó dá a fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Allāhu sì ń jẹ́ Onímọ̀, Ọlọ́gbọ́n. Suuratun Nisāi: 111 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ مِنْ أَجْلِ ذَٰلِكَ كَتَبْنَا عَلَىٰ بَنِي إِسْرَائِيلَ أَنَّهُ مَن قَتَلَ نَفْسًا بِغَيْرِ نَفْسٍ أَوْ فَسَادٍ فِي الْأَرْضِ فَكَأَنَّمَا قَتَلَ النَّاسَ جَمِيعًا وَمَنْ أَحْيَاهَا فَكَأَنَّمَا أَحْيَا النَّاسَ جَمِيعًا }

Nítorí ìyẹn, A sì ṣe é ní òfin fún àwọn ọmọ ’Isrọ̄’īl pé dájúdájú ẹnikẹ́ni tí ó bá pa ẹ̀mí (ènìyàn) kan láìjẹ́ nítorí pípa ẹ̀mí (ènìyàn) kan tàbí ṣíṣe ìbàjẹ́ kan lórí ilẹ̀, ó dà bí ẹni tí ó pa gbogbo ènìyàn pátápátá. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì mú ẹ̀mí (ènìyàn) ṣẹ̀mí, ó dà bí ẹni tí ó mú gbogbo ènìyàn ṣẹ̀mí pátápátá. Suuratul Māidah: 32. Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«لَا تُقْتَلُ نَفْسٌ ظُلْمًا إِلَّا كَانَ عَلَى ابْنِ آدَمَ الْأَوَّلِ كِفْلٌ مِنْ دَمِهَا لِأَنَّهُ كَانَ أَوَّلَ مَنْ سَنَّ الْقَتْلَ»

Won o nii pa ẹ̀mi kan ni ti abosi ayaafi ki ipin kan ninu ẹ̀jẹ rẹ̀ o maa bẹ lori ọmọ Anabi Ādam alakọkọ, torípé oun ni ẹni akọkọ ti o fi ilana pipa èèyàn lelẹ. Sohiihu Muslim: 5150

## 18. Islaam se okunrin ati obinrin ni deede ara wọn nibi iṣẹ ati ojuse ati ẹsan.

Islaam se okunrin ati obinrin ni deede ara wọn nibi iṣẹ ati ojuse ati ẹsan, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَمَن يَعْمَلْ مِنَ الصَّالِحَاتِ مِن ذَكَرٍ أَوْ أُنثَىٰ وَهُوَ مُؤْمِنٌ فَأُولَٰئِكَ يَدْخُلُونَ الْجَنَّةَ وَلَا يُظْلَمُونَ نَقِيرًا}

Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣiṣẹ́ rere, yálà ọkùnrin tàbí obìnrin, onígbàgbọ́ òdodo sì ni, àwọn wọ̀nyẹn l’ó máa wọ inú

Ọgbà Ìdẹ̀ra. A ò sì níí ṣàbòsí èékán kóró dàbínù fún wọn. Suuratun Nisāi: 124 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ مَنْ عَمِلَ صَالِحًا مِّن ذَكَرٍ أَوْ أُنثَىٰ وَهُوَ مُؤْمِنٌ فَلَنُحْيِيَنَّهُ حَيَاةً طَيِّبَةً ۖ وَلَنَجْزِيَنَّهُمْ أَجْرَهُم بِأَحْسَنِ مَا كَانُوا يَعْمَلُونَ }

Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere, ọkùnrin ni tàbí obìnrin, ó sì jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo, dájúdájú A óò jẹ́ kí ó lo ìgbésí ayé t'ó dára. Dájúdájú A ó sì fi èyí t'ó dára jùlọ sí ohun tí wọ́n ń ṣe nísẹ́ san wọ́n ní ẹ̀san wọn. Suuratun Nahl: 97. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ مَنْ عَمِلَ سَيِّئَةً فَلَا يُجْزَىٰ إِلَّا مِثْلَهَا ۖ وَمَنْ عَمِلَ صَالِحًا مِّن ذَكَرٍ أَوْ أُنثَىٰ وَهُوَ مُؤْمِنٌ فَأُولَٰئِكَ يَدْخُلُونَ الْجَنَّةَ يُرْزَقُونَ فِيهَا بِغَيْرِ حِسَابٍ }

Ẹni tí ó bá ṣe aburú kan, Wọn kò níí san án ní ẹ̀san kan àyàfi irú rẹ̀. Ẹni tí ó bá sì ṣe iṣẹ́ rere ní ọkùnrin tàbí ní obìnrin, tí ó sì jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo, àwọn wọ̀nyẹn ni wọ́n máa wọ inú Ọgbà Ìdẹ̀ra. Wọn yóò máa pèsè àrísìkí fún wọn nínú rẹ̀ láì la ìṣírò lọ. Suuratu Qāfir: 40. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ إِنَّ الْمُسْلِمِينَ وَالْمُسْلِمَاتِ وَالْمُؤْمِنِينَ وَالْمُؤْمِنَاتِ وَالْقَانِتِينَ وَالْقَانِتَاتِ وَالصَّادِقِينَ وَالصَّادِقَاتِ وَالصَّابِرِينَ وَالصَّابِرَاتِ وَالْخَاشِعِينَ وَالْخَاشِعَاتِ وَالْمُتَصَدِّقِينَ وَالْمُتَصَدِّقَاتِ وَالصَّائِمِينَ وَالصَّائِمَاتِ وَالْحَافِظِينَ فُرُوجَهُمْ وَالْحَافِظَاتِ وَالذَّاكِرِينَ اللَّهَ كَثِيرًا وَالذَّاكِرَاتِ أَعَدَّ اللَّهُ لَهُم مَّغْفِرَةً وَأَجْرًا عَظِيمًا}

Dájúdájú àwọn mùsùlùmí lọ́kùnrin àti mùsùlùmí lóbìnrin, àwọn onígbàgbọ́ òdodo lọ́kùnrin àti àwọn onígbàgbọ́ òdodo lóbìnrin, àwọn olùtẹ̀lé-àṣẹ Allāhu lọ́kùnrin àti àwọn olùtẹ̀lé-àṣẹ Allāhu lóbìnrin, àwọn olódodo lọ́kùnrin àti àwọn olódodo lóbìnrin, àwọn onísùúrù lọ́kùnrin àti àwọn onísùúrù lóbìnrin, àwọn olùpáyà Allāhu lọ́kùnrin àti àwọn olùpáyà Allāhu

lóbìnrin, àwọn olùtọrẹ lọ́kùnrin àti àwọn olùtọrẹ lóbìnrin, àwọn aláàwẹ̀ lọ́kùnrin àti àwọn aláàwẹ̀ lóbìnrin, àwọn t'ó ń ṣọ́ abẹ́ wọn lọ́kùnrin àti àwọn t'ó ń ṣọ́ abẹ́ wọn lóbìnrin, àwọn olùrántí Allāhu ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ lọ́kùnrin àti àwọn olùrántí Allāhu (ní ọ̀pọ̀lọ́pọ̀) lóbìnrin; Allāhu ti pèsè àforíjìn àti ẹ̀san ńlá sílẹ̀ dè wọ́n. Suuratul A'azāb: 35.

## 19. Islaam pọn obìnrin le, o si ka wọn kun pe bákan náà ni wọ́n ṣe ri pẹ̀lú awọn ọkunrin, o si ṣe inawo ni dandan lori ọkùnrin ti o ba ni ikapa, ìnáwó ọmọbìnrin jẹ dandan lori bàbá rẹ, ti ìyá si jẹ dandan lórí ọmọkùnrin rẹ tí ó bá ti bàlágà ti o si ni ikapa, ti ìyàwó si jẹ dandan lori ọkọ rẹ.

Islam ka àwọn obìnrin kun pe bákan náà ni wọ́n ṣe ri pẹ̀lú awọn ọkunrin Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«إن النساء شقائق الرجال»

"Dajudaju awọn obinrin ri bákan náà pẹ̀lú àwọn ọkùnrin" Tirmiziy ni o gba a wa (113)

Ninu apọnle Islaam fún obìnrin ni wipe Islaam ṣe inawo ìyá ni dandan lori ọmọ rẹ ti o ba jẹẹnití o ni ikapa. Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«يَدُ الْمُعْطِي الْعُلْيَا أُمَّكَ وَأَبَاكَ وَأُخْتَكَ وَأَخَاكَ ثُمَّ أَدْنَاكَ أَدْنَاكَ»

"Ọwọ tí ba n fún ni òkè ni máa n gbe, bẹ̀rẹ̀ láti orí àwọn ti ninawo le wọn lórí kàn ọ́: ìyá rẹ, ati baba rẹ, ati ọmọ'ya rẹ l'obinrin, ati ọmọ'ya l'ọkunrin, ati awọn ẹbí rẹ ti wọn sunmọ ọ jù, lẹ́yìn náà àwọn ti wọn tun sunmọ ọn tẹ̀lé wọn". Imaamu Ahmad lo gba a wa. Ati pe alaye ipo awọn òbí mejeeji sí n bọ pẹlu iyọnda Ọlọhun ni ìpínrọ̀ẹ̀lẹ̀ẹ̀kọkandìnlọgbọ̀n (29).

Ati pe ninu apọnle Islaam fún obìnrin ni wipe o ṣe e ni dandan fún ọkọ láti maa náwó lórí ìyàwó rẹ ti o ba jẹẹni tí o ni ikapa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ لِيُنفِقْ ذُو سَعَةٍ مِّن سَعَتِهِ ۖ وَمَن قُدِرَ عَلَيْهِ رِزْقُهُ فَلْيُنفِقْ مِمَّا آتَاهُ اللَّهُ ۚ لَا يُكَلِّفُ اللَّهُ نَفْسًا إِلَّا مَا آتَاهَا ۚ سَيَجْعَلُ اللَّهُ بَعْدَ عُسْرٍ يُسْرًا}

Kí ọlọ́rọ̀ ná nínú ọrọ̀ rẹ̀. Ẹni tí A sì díwọ̀n arísìkí rẹ̀ fún (níwọ̀nba), kí ó ná nínú ohun tí Allāhu fún un. Allāhu kò làbọ ẹ̀mí kan lọ́rùn àyàfi ǹǹkan tí Ó fún un. Allāhu yó sì mú ìrọ̀rùn wá lẹ́yìn ìnira. Suuratut Tolāq: 7

وسَأَلَ النبيَ صلى الله عليه وسلم رَجُلٌ: مَا حَقُّ الْمَرْأَةِ عَلَى الزَّوْجِ؟ قَالَ: «تُطْعِمُهَا إِذَا طَعِمْتَ وَتَكْسُوهَا إِذَا اكْتَسَيْتَ وَلَا تَضْرِبِ الْوَجْهَ وَلَا تُقَبِّحْ»

Arakunrin kan bi Anabi - kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a - leere wipe: Kí ni iwọ ìyàwó lórí ọkọ rẹ? O sọ pe: "kí ọ maa fún un ni oúnjẹ nígbà tí o ba n jẹun, kí o si tun máa fún un ni aṣọ wọ nígbà tí o ba n wọ aṣọ, ati pe oo gbọdọ gba a ni oju, oo sì gbọdọ sọrọ burúkú sí i. Imaamu Ahmad lo gba a wa. Òjíṣẹ Ọlọhun- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ l'ẹniti n ṣe alaye díẹ̀ ninu awọn iwọ awọn obinrin lórí àwọn ọkọ wọn.

«وَلَهُنَّ عَلَيْكُمْ رِزْقُهُنَّ وَكِسْوَتُهُنَّ بِالْمَعْرُوفِ»

O pon dandan le yin lori fun awon iyawo yin jije mimu won ati aso wiwo won pelu daadaa (ohun ti e ti ba saaba) Sohiihu ti Muslim O tun sọ– ki ike ati ola Olohun maa ba a– pe:

«كَفَى بِالْمَرْءِ إِثْمًا أَنْ يُضَيِّعَ مَنْ يَقُوتُ»

O ti to ni ẹ̀ṣẹ̀ fun omoniyan ki o fi ẹniti o n fun un ni ounje rare Imaamu Ahmad ni o gba a wa. Al khatoobiy so wipe: Gbolohun re ti o so pe: "mon yaquut" ohun ti o gba lero ni eniti jije-mimu re je dandan le e ni ori, atipe itumo re dabi wipe o so fun olutọrẹ wipe: ma se tore pelu nkan ti ko to awon ara ile re je ni ajeseku leniti o n reti ẹsan pelu re; iyen le pada di ese ti o ba fi won rare.

Ninu aponle ti Islaam se fun obinrin ni wipe o se inawo omobinrin ni dandan lori baba re, Oba Alloohu ti ola Re ga so wipe:

{وَالْوَالِدَاتُ يُرْضِعْنَ أَوْلَادَهُنَّ حَوْلَيْنِ كَامِلَيْنِ ۖ لِمَنْ أَرَادَ أَن يُتِمَّ الرَّضَاعَةَ ۚ وَعَلَى الْمَوْلُودِ لَهُ رِزْقُهُنَّ وَكِسْوَتُهُنَّ بِالْمَعْرُوفِ}

Àwọn abiyamọ yóò máa fún àwọn ọmọ wọn ní ọyàn mu fún ọdún méjì gbáko, fún ẹni tí ó bá fẹ́ parí (àsìkò) ìfọ́mọlọ́yàn. Ojúṣe ni fún ẹni tí wọ́n bímọ fún láti máa ṣe (ètò) ìjẹ-ìmu wọn àti aṣọ wọn ní ọ̀nà t'ó dára Suuratul Baqorah: 233 Alloohu wa se alaye wipe o je dandan lori baba ti won bi omo fun, fifun omo re ni ounje ati aso pelu daadaa (nnkan ti won ti ba saaba).

{ فَإِنْ أَرْضَعْنَ لَكُمْ فَآتُوهُنَّ أُجُورَهُنَّ }

Ti won ba ba yin fun omo ni oyan, ki e ya fun won ni awon owo ọya won. Suuratut Tolaaq: 6. Alloohu wa

se owo ọya ifun omo ni oyan ni dandan lori baba; o wa toka si wipe inawo omo lori baba lo wa, ati wipe gbolohun Alwaladu (omo) o ko okunrin ati obinrin sinu. Atipe o nbe ninu hadith ti o n bo yii itoka lori jije dandan inawo iyawo ati omo re lori baba. Lati odo Aaisha – ki Alloohu yonu si i -: dajudaju arabinrin Hindu so fun Anabi – ki ike ati ola Olohun maa ba a – wipe: dajudaju baba Sufyaan je enikan ti o ni ahun, ti mo si maa n bukaata si ki n mu ninu owo re, o so pe (Anabi):

«خُذِي مَا يَكْفِيكِ وَوَلَدَكِ بِالْمَعْرُوفِ»

"Mu ninu owo re nkan ti yóò to iwo pelu omo re ni ibamu si nnkan ti e ti ba saaba. Bukhaari ni o gba a wa. Anabi ti o je ọlọrẹ naa si se alaye ola ti n be fun nina owo lori awon omobinrin ati awọn ọmọ-ìyá lobinrin, Ojise Olohun – ki ike ati ola Olohun maa ba a – wa so wipe:

«مَنْ عَالَ ابْنَتَيْنِ أَوْ ثَلَاثَ بَنَاتٍ أَوْ أُخْتَيْنِ أَوْ ثَلَاثَ أَخَوَاتٍ حَتَّى يَبِنَّ أَوْ يَمُوتَ عَنْهُنَّ كُنْتُ أَنَا وَهُوَ كَهَاتَيْنِ. وَأَشَارَ بِأُصْبُعَيْهِ السَّبَّابَةِ وَالْوُسْطَى»

"Enikeni ti o ba toju omobinrin meji tabi meta, tabi ọmọ-ìyá lobinrin meji tabi meta titi ti won fi ja kuro lodo re (boya won ku ni tabi won ni oko), tabi ki o ku saaju won, emi pelu re o wa bayii. O (Anabi) wa se apejuwe wiwapo won pelu ika ifabela re ati ti aarin. As silsilah As sohiiha 296.

## 20. Iku kii se titan gbere, ati pe iku a maa pa ara ati emi, iku emi si ni pipinya re kuro ni ara, leyin naa yoo

**pada si ara leyin igbedide ojo Alukiyaamọ, ati pe Emi o ni bo si ara miran leyin iku ko si nii pada sinu ara mii (akudaaya).**

Iku kii se titan gbere, Olohun ti Ola Re ga so wipe: Sọ pé:

{قُلْ يَتَوَفَّاكُم مَّلَكُ الْمَوْتِ الَّذِي وُكِّلَ بِكُمْ ثُمَّ إِلَىٰ رَبِّكُمْ تُرْجَعُونَ}

Sọ pé: "Mọlāika ikú èyí tí A fi tì yín máa gba ẹ̀mí yín. Lẹ́yìn náà, ọ̀dọ̀ Olúwa yín ni wọn máa da yín padà sí." Suuratus Sajdah: 11 Atipe iku a maa pa ara ati emi, iku emi si ni pipinya re kuro ni ara, leyin naa yio pada si ara leyin igbedide ojo Alukiyaamọ, Olohun ti Ola Re ga so wipe:

{ اللَّهُ يَتَوَفَّى الْأَنفُسَ حِينَ مَوْتِهَا وَالَّتِي لَمْ تَمُتْ فِي مَنَامِهَا ۖ فَيُمْسِكُ الَّتِي قَضَىٰ عَلَيْهَا الْمَوْتَ وَيُرْسِلُ الْأُخْرَىٰ إِلَىٰ أَجَلٍ مُّسَمًّى ۚ إِنَّ فِي ذَٰلِكَ لَآيَاتٍ لِّقَوْمٍ يَتَفَكَّرُونَ}

Allāhu l'Ó ń gba àwọn ẹ̀mí ní àkókò ikú wọn àti (àwọn ẹ̀mí) tí kò kú sójú oorun wọn. Ó ń mú (àwọn ẹ̀mí) tí Ó ti pèbùbù ikú lé lórí mọ́lẹ̀. Ó sì ń fi àwọn yòókù sílẹ̀ títí di gbèdéke àkókò kan. Dájúdájú àwọn àmì wà nínú ìyẹn fún ìjọ t'ó ń ronú. Suuratuz Zumar: 42. Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«إِنَّ الرُّوحَ إِذَا قُبِضَ تَبِعَهُ الْبَصَرُ»

"Dajudaju ti won ba ti gba emi irina naa maa n tele e". Muslim ni o gba a wa pelu ẹgbawa rẹ mejeeji Ati pe

leyin iku omoniyan o kuro ni ile iṣẹ́ lo si ile ẹsan, Olohun ti Ola Re ga so pe:

{ إِلَيْهِ مَرْجِعُكُمْ جَمِيعًا ۖ وَعْدَ اللَّهِ حَقًّا ۚ إِنَّهُ يَبْدَأُ الْخَلْقَ ثُمَّ يُعِيدُهُ لِيَجْزِيَ الَّذِينَ آمَنُوا وَعَمِلُوا الصَّالِحَاتِ بِالْقِسْطِ ۚ وَالَّذِينَ كَفَرُوا لَهُمْ شَرَابٌ مِّنْ حَمِيمٍ وَعَذَابٌ أَلِيمٌ بِمَا كَانُوا يَكْفُرُونَ }

Ọdọ̀ Rẹ̀ ni ibùpadàsí gbogbo yín. (Ó jẹ́) àdéhùn Allāhu ní òdodo. Dájúdájú Òun l'Ó ń pilẹ̀ dídá ẹ̀dá. Lẹ́yìn náà, Ó máa da á padà (sọ́dọ̀ Rẹ̀) nítorí kí Ó lè fi déédé san ẹ̀san fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣe iṣẹ́ rere. Àwọn t'ó sì ṣàì gbàgbọ́, ohun mímu gbígbóná àti ìyà ẹlẹ́ta-eléro ń bẹ fún wọn nítorí pé wọ́n ṣàì gbàgbọ́. Suuratu Yuunus: 4

Ati pe ẹ̀mí o ni bo si ara miran leyin iku ko si da (akudaaya), pipe apemora akudaaya si je nkan ti laakaye ati igbọnmọ ko tọka si, ati pe ko si egbawa Kankan ti o n jẹrii si adisokan yii lati odo awon Anabi Olohun – ki alaafia maa je ti gbogbo won.

## 21. Islaam n pepe lo si ibi nini igbagbo pelu awon ipile igbagbo ti o tobi, awon naa ni nini igbagbo si Olohun ati awon Malaaika Rẹ, ati nini igbagbo si awon iwe Olohun gẹ́gẹ́ bíi Taoreeta ati Injiila ati Zabuura – siwaju ki won o to yi oro inu won pada – ati Alukurani, ati nini igbagbo si gbogbo awon Anabi ati awon Ojise- ki ola maa ba gbogbo

## won- ati ki a ni igbagbo si ẹni ti o kẹyin won, oun naa ni Muhammad Ojise Olohun, igbeyin awon Anabi ati awon Ojise, ati nini igbagbo si ojo ikẹyin, ki a si tun mo wipe kani isemi ile-aye je opin ni; ere ponbele ni isemi ati bibẹ o ba jẹ, ati nini igbagbo si kadara

Islaam n pepe lo si ibi nini igbagbo si awon ipile igbagbo ti o tobi, eleyi ti gbogbo awon Anabi ati Ojise – ki ola o maa ba won – pepe si, awon naa ni:

Alakoko: Nini igbagbo si Alloohu ni Oluwa, Adeda, Olupese-arisiki, Oludari-aye, ati pe Oun nikan ni O lẹ́tọ̀ọ́ si ijosin, ati pe jijosin fun gbogbo nkan ti o ba ti yato si I ibaje ni, ati pe gbogbo nkan ti won ba n josin fun yato si I ibaje ni, ijosin o si lẹ́tọ̀ọ́ ayaafi fun Un, ijosin o si le daa ayaafi fun Un. Alaye awon eri oro yii si ti saaju nibi ipinrọ kejo (8).

Olohun– mimo ni fun Un– dárúkọ àwọn ipilẹ ti o tobi yii ninu awọn aaya ti o pọ ni ààyè ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ninu AL-Quraan ti o tobi, ninu re ni gbólóhùn Olohun ti O sọ pe:

{آمَنَ الرَّسُولُ بِمَا أُنزِلَ إِلَيْهِ مِن رَّبِّهِ وَالْمُؤْمِنُونَ ۚ كُلٌّ آمَنَ بِاللَّهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ لَا نُفَرِّقُ بَيْنَ أَحَدٍ مِّن رُّسُلِهِ ۚ وَقَالُوا سَمِعْنَا وَأَطَعْنَا ۖ غُفْرَانَكَ رَبَّنَا وَإِلَيْكَ الْمَصِيرُ }

Òjíṣẹ́ náà (sollalāhu 'alayhi wa sallam) gbàgbọ́ nínú ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún un láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀. Àwọn onígbàgbọ́ òdodo náà (gbàgbọ́ nínú rẹ̀). Ẹnì kọ̀ọ̀kan

(wọn) gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀ àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Wọ́n sì sọ pé: "A gbọ́ (àṣẹ), a sì tẹ̀lé (àṣẹ). À ń tọrọ àforíjìn Rẹ, Olúwa wa. Ọ̀dọ̀ Rẹ sì ni àbọ̀ ẹ̀dá." Suuratul Baqara: 285 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ لَّيْسَ الْبِرَّ أَن تُوَلُّوا وُجُوهَكُمْ قِبَلَ الْمَشْرِقِ وَالْمَغْرِبِ وَلَٰكِنَّ الْبِرَّ مَنْ آمَنَ بِاللَّهِ وَالْيَوْمِ الْآخِرِ وَالْمَلَائِكَةِ وَالْكِتَابِ وَالنَّبِيِّينَ وَآتَى الْمَالَ عَلَىٰ حُبِّهِ ذَوِي الْقُرْبَىٰ وَالْيَتَامَىٰ وَالْمَسَاكِينَ وَابْنَ السَّبِيلِ وَالسَّائِلِينَ وَفِي الرِّقَابِ وَأَقَامَ الصَّلَاةَ وَآتَى الزَّكَاةَ وَالْمُوفُونَ بِعَهْدِهِمْ إِذَا عَاهَدُوا ۖ وَالصَّابِرِينَ فِي الْبَأْسَاءِ وَالضَّرَّاءِ وَحِينَ الْبَأْسِ ۗ أُولَٰئِكَ الَّذِينَ صَدَقُوا ۖ وَأُولَٰئِكَ هُمُ الْمُتَّقُونَ }

Kì í ṣe ohun rere ni kí ẹ kọjú sí agbègbè ibùyọ òòrùn àti ibùwọ̀ òòrùn, àmọ́ (olùṣe) rere ni ẹnikẹ́ni t'ó bá gbàgbọ́ nínú Allāhu, Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, àwọn mọlāika, Tírà (al-Ḳur'ān), àti àwọn Ànábì. Tòhun ti ìfẹ́ tí olùṣe-rere ní sí owó, ó tún ń fi owó náà tọrẹ fún àwọn ẹbí, àwọn ọmọ òrukàn, àwọn mẹ̀kúnnù, onírìn-àjò (tí agara dá), àwọn atọrọjẹ àti (ìtúsílẹ̀) l'óko ẹrú. (Ẹni rere) yó máa kírun, yó sì máa yọ Zakāh. (Ẹni rere ni) àwọn t'ó ń mú àdéhùn wọn ṣe nígbà tí wọ́n bá ṣe àdéhùn àti àwọn onísùúrù nígbà àìríná-àìrílò, nígbà àìlera àti l'ójú ogun ẹ̀sìn. Àwọn wọ̀nyẹn ni àwọn t'ó ṣe (iṣẹ́) òdodo. Àwọn wọ̀nyẹn, àwọn sì ni olùbẹ̀rù (Allāhu). Suuratul Baqara: 177 Alloohu si pepe lọ sibi nini ìgbàgbọ́ si awọn ipilẹ yii, O si tun ṣe alaye wipe ẹni ti o ba se aìgbàgbọ́ si i, o ti sina ni isina ti o jina tefetefe, Ọba Alloohu ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا آمِنُوا بِاللَّهِ وَرَسُولِهِ وَالْكِتَابِ الَّذِي نَزَّلَ عَلَىٰ رَسُولِهِ وَالْكِتَابِ الَّذِي أَنزَلَ مِن قَبْلُ ۚ وَمَن يَكْفُرْ بِاللَّهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ وَالْيَوْمِ الْآخِرِ فَقَدْ ضَلَّ ضَلَالًا بَعِيدًا}

Ẹyin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ gbàgbọ́ dáadáa nínú Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀, àti Tírà tí (Allāhu) sọ̀kalẹ̀ fún Òjíṣẹ́ Rẹ̀, àti Tírà tí Ó sọ̀kalẹ̀ ṣíwájú. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣàì gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀, àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀ àti Ọjọ́ Ìkẹyìn, dájúdájú ó ti ṣìnà ní ìṣìnà t’ó jìnnà tefétefé. Suuratun-Nisai: 136. Ninu Hadith ti o wa lati ọdọ Umar omo Al-Khatoob– ki Alloohu ba wa yonu si i– o so pe:

(بَيْنَمَا نَحْنُ عِنْدَ رَسُولِ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ ذَاتَ يَوْمٍ إِذْ طَلَعَ عَلَيْنَا رَجُلٌ شَدِيدُ بَيَاضِ الثِّيَابِ شَدِيدُ سَوَادِ الشَّعَرِ لَا يُرَى عَلَيْهِ أَثَرُ السَّفَرِ وَلَا يَعْرِفُهُ مِنَّا أَحَدٌ حَتَّى جَلَسَ إِلَى النَّبِيِّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَأَسْنَدَ رُكْبَتَيْهِ إِلَى رُكْبَتَيْهِ وَوَضَعَ كَفَّيْهِ عَلَى فَخِذَيْهِ وَقَالَ: يَا مُحَمَّدُ أَخْبِرْنِي عَنِ الْإِسْلَامِ فَقَالَ رَسُولُ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ: «الْإِسْلَامُ أَنْ تَشْهَدَ أَنْ لَا إِلَهَ إِلَّا اللهُ وَأَنَّ مُحَمَّدًا رَسُولُ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ وَتُقِيمَ الصَّلَاةَ وَتُؤْتِيَ الزَّكَاةَ وَتَصُومَ رَمَضَانَ وَتَحُجَّ الْبَيْتَ إِنِ اسْتَطَعْتَ إِلَيْهِ سَبِيلًا» قَالَ: صَدَقْتَ قَالَ: فَعَجِبْنَا لَهُ يَسْأَلُهُ وَيُصَدِّقُهُ قَالَ: فَأَخْبِرْنِي عَنِ الْإِيمَانِ قَالَ: «أَنْ تُؤْمِنَ بِاللهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ وَالْيَوْمِ الْآخِرِ وَتُؤْمِنَ بِالْقَدَرِ خَيْرِهِ وَشَرِّهِ» قَالَ: صَدَقْتَ قَالَ: فَأَخْبِرْنِي عَنِ الْإِحْسَانِ قَالَ: «أَنْ تَعْبُدَ اللهَ كَأَنَّكَ تَرَاهُ فَإِنْ لَمْ تَكُنْ تَرَاهُ فَإِنَّهُ يَرَاكَ»

Laarin igba ti a jókòó si ọdọ ojiṣẹ Ọlọhun– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– ni ọjọ kan, ni arakunrin kan ba wọle to wa wa, aṣọ rẹ si funfun gboo, irun ori rẹ si dudu kirikiri, ko si àpẹẹrẹ arinrin-ajo kankan lara re, ẹnikan kan o si mọ ọn ninu wa. Titi ti o fi jokoo si ọdọ Anabi– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– o wa fi orunkun rẹ mejeeji ti orunkun Anabi mejeeji, o si gbe ọwọ rẹ mejeeji le ori itan rẹ mejeeji, o wa sọ pe: Irẹ Muhammad, fun mi niro nipa Islam. Ojisẹ Ọlọhun

Olohun– ki ike ati ola Oloun maa ba a– wa sọ pe: Ohun ti nje Islam ni ki o jẹri wipe ko si ọba kankan ayafi Allaah ati pe Muhammad ojiṣẹ Allaah ni, ki o si maa gbe irun duro, ki o si maa yọ zakah, ki o si maa lọ si ile Ọlọhun ti o ba ni ikapa ipese ti o fi le lọ. O sọ pe: Ododo lo sọ. O wa ya wa lẹ́nu fun un, oun ni n bi i leere ibeere, oun lo tun n sọ fun un wipe ododo lo so! O sọ pe: fun mi niro nipa Al-Iimaan {Igbagbo}. O sọ pe: Ki o gba Ọlọhun Ọba gbọ ati awọn Malaika Rẹ ati awọn tira Rẹ ati awọn ojiṣẹ Rẹ ati ọjọ ìkẹhìn, ki o si ni igbagbọ si kadara daada rẹ ni ati aida rẹ. O sọ pe: ododo lo so. O sọ pe: Fun mi niro nipa Al-I'isaan {Ṣíṣe daadaa}. O sọ pe: Ki o maa jọsin fun Ọlọhun gẹgẹ bi wipe o nri I, ti o ko ba waa ri I dajudaju Oun ri ẹ. O sọ pe: Fun mi niro nipa As-saahah {Igbati aye a parẹ}. O sọ pe: Ẹni ti a n bi leere nipa rẹ ko ni imọ ju ẹni ti o n beere lọ. O sọ pe: Fun mi niro nipa awọn amin ti aa maa ri ti ayẹ ba ti fẹ́ parẹ. O sọ pe: Ki ẹrú maa bi olowo rẹ, ati ki o maa ri awọn arin ma wọ bata ati awọn arin ihoho ati awọn alaini ti wọn a maa fi ile giga ṣe iyanran. Lẹyin naa ni o wa lọ, ni mo wa ko ara ro díẹ̀, lẹyin naa ni o wa sọ pe: Irẹ Umar, njẹ o mọ ẹni ti o nbeere ibeere? Mo sọ pe: Ọlọhun ati ojiṣẹ Rẹ nikan lo mọ ọn, o sọ pe: Dajudaju Jubriil ni o wa bayin lati wa fi ẹsin yin mọ yin. Sohiihu Muslim: 8 Ninu Hadith yii, Jubril– ki ola maa ba a– wa si odo Ojise Olohun– ki ike ati ola Olohun maa ba a– o si bi i leere nipa awon ipo esin, awon naa si ni: Al-Islaam ati Al-Imaan ati Al-Ihsaan. Ojise ti nse Muhammad– ki ike ati ola Olohun maa ba

a– si fesi fun un, leyin naa Anọbi Muhammad – ki ike ati ola Olohun maa ba a – fun awon saabe re – ki Olohun yonu si won – ni iro wipe Jubril ni ẹni yẹn, o wa lati wa fi esin won mo won. Eleyii oun naa Esin Islaam ti o je oro atorunwa ti Jubril – ki ola o maa ba a – mu wa, ti Anọbi Muhammad – ki ike ati ola Olohun maa ba a – si mu un de etigbo awon eeyan, ti awon saabe re – ki Olohun yonu si won – si ha a, won si tun mu un de etigbo awon eeyan leyin re.

Eleekeji: Ninu igbagbo si awon Malaika, ati pe awon (malaika) agbaye kan ti a ko fi oju ri ni won, Alloohu da won, O si se won lori aworan kan ti a se adayanri, O si gbe awon ise ti o tobi le won ni owo, ninu eyi ti o gbọnńgbọn julo ninu awon ise won ni mimu awon oro atorunwa de odo awon Ojise ati awon Anabi– ki ola o maa ba won– eniti o si gbọnngbọn julo ninu awon Malaaika ni Jubril– ki ola o maa ba a– ati pe ninu ohun ti o ntoka si sisokale Jubril pelu mimu imisi (wah'y) wa ba awon Òjíṣẹ– ki ike ati ola o maa ba wọn– ni gbolohun Olohun ti ola Rẹ ga ti o wi pe:

{ يُنَزِّلُ الْمَلَائِكَةَ بِالرُّوحِ مِنْ أَمْرِهِ عَلَىٰ مَن يَشَاءُ مِنْ عِبَادِهِ أَنْ أَنذِرُوا أَنَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا أَنَا فَاتَّقُونِ }

(Allāhu) ń fi àṣẹ Rẹ̀ sọ mọlāika (Jibrīl) kalẹ̀ láti máa mú ìmísí wá díẹ̀díẹ̀ fún ẹnikẹ́ni tí Ó bá fẹ́ (bẹ́ẹ̀ fún) nínú àwọn ẹrúsìn Rẹ̀ nítorí kí ẹ lè fi ṣe ìkìlọ̀ pé: "Dájúdájú kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi. Nítorí náà, ẹ bẹ̀rù Mi." Suuratun Nahl: 2. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ وَإِنَّهُ لَتَنزِيلُ رَبِّ الْعَالَمِينَ (192) نَزَلَ بِهِ الرُّوحُ الْأَمِينُ (193) عَلَىٰ قَلْبِكَ لِتَكُونَ مِنَ الْمُنذِرِينَ (194) بِلِسَانٍ عَرَبِيٍّ مُّبِينٍ (195) وَإِنَّهُ لَفِي زُبُرِ الْأَوَّلِينَ (196) }

Dájúdájú al-Ƙur'ān, wọ́n sọ̀ ọ́ kalẹ̀ ni láti ọ̀dọ̀ Olúwa gbogbo ẹ̀dá.

Mọlāika Jibrīl, olùfọkàntán l'ó sọ̀ ọ́ kalẹ̀

sínú ọkàn rẹ nítorí kí o lè wà nínú àwọn olùkìlọ̀

pẹ̀lú èdè Lárúbáwá pọ́nńbélé.

Dájúdájú (ọ̀rọ̀ nípa rẹ̀) ti wà nínú ìpín-ìpín Tírà àwọn ẹni àkọ́kọ́. As-Shuaraa' 192-196

Eleeketa: Nini igbagbo si awon Tira Ọlọhun (Atorunwa) gẹ́gẹ́ bii At-Taorah ati Al-Injiil ati Az-Zabuur – siwaju ki won to yi oro inu re pada – ati Al-Quraan, Ọlọhun ti Ola Rẹ ga sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا آمِنُوا بِاللَّهِ وَرَسُولِهِ وَالْكِتَابِ الَّذِي نَزَّلَ عَلَىٰ رَسُولِهِ وَالْكِتَابِ الَّذِي أَنزَلَ مِن قَبْلُ ۚ وَمَن يَكْفُرْ بِاللَّهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ وَالْيَوْمِ الْآخِرِ فَقَدْ ضَلَّ ضَلَالًا بَعِيدًا}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ gbàgbọ́ dáadáa nínú Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀, àti Tírà tí (Allāhu) sọ̀kalẹ̀ fún Òjíṣẹ́ Rẹ̀, àti Tírà tí Ó sọ̀kalẹ̀ ṣíwájú. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣàì gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀, àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀ àti Ọjọ́ Ìkẹyìn, dájúdájú ó ti ṣìnà ní ìṣìnà t'ó jìnnà tefétefé. Suuratun-Nisai: 136. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{نَزَّلَ عَلَيْكَ الْكِتَابَ بِالْحَقِّ مُصَدِّقًا لِّمَا بَيْنَ يَدَيْهِ وَأَنزَلَ التَّوْرَاةَ وَالْإِنجِيلَ (3) مِن قَبْلُ هُدًى لِّلنَّاسِ وَأَنزَلَ الْفُرْقَانَ ۗ إِنَّ الَّذِينَ كَفَرُوا بِآيَاتِ اللَّهِ لَهُمْ عَذَابٌ شَدِيدٌ ۗ وَاللَّهُ عَزِيزٌ ذُو انتِقَامٍ (4) }

Ó sọ Tírà (al-Ḳur’ān) kalẹ̀ fún ọ pẹ̀lú òdodo, tí ó ń fi ohun t’ó jẹ́ òdodo rinlẹ̀ nípa èyí t’ó wà ṣíwájú rẹ̀. Ó sì sọ Taorāh àti ’Injīl kalẹ̀

ní ìṣaájú. Ìmọ̀nà sì ni fún àwọn ènìyàn.1 Ó tún sọ ọ̀rọ̀-ìpínyà (ọ̀rọ̀ t’ó ń ṣèpínyà láàarin òdodo àti irọ́) kalẹ̀.2 Dájúdájú àwọn t’ó ṣàì gbàgbọ́ nínú àwọn āyah Allāhu, ìyà t’ó le ń bẹ fún wọn. Allāhu sì ni Alágbára, Olùgbẹ̀san. Suuratu Al Imraan: 3-4. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ ءَامَنَ ٱلرَّسُولُ بِمَآ أُنزِلَ إِلَيۡهِ مِن رَّبِّهِۦ وَٱلۡمُؤۡمِنُونَۚ كُلٌّ ءَامَنَ بِٱللَّهِ وَمَلَٰٓئِكَتِهِۦ وَكُتُبِهِۦ وَرُسُلِهِۦ لَا نُفَرِّقُ بَيۡنَ أَحَدٖ مِّن رُّسُلِهِۦۚ وَقَالُواْ سَمِعۡنَا وَأَطَعۡنَاۖ غُفۡرَانَكَ رَبَّنَا وَإِلَيۡكَ ٱلۡمَصِيرُ }

Òjíṣẹ́ náà (sollalāhu 'alayhi wa sallam) gbàgbọ́ nínú ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún un láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀. Àwọn onígbàgbọ́ òdodo náà (gbàgbọ́ nínú rẹ̀). Ẹnì kọ̀ọ̀kan (wọn) gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀ àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Wọ́n sì sọ pé: “A gbọ́ (àṣẹ), a sì tẹ̀lé (àṣẹ). À ń tọrọ àforíjìn Rẹ, Olúwa wa. Ọ̀dọ̀ Rẹ sì ni àbọ̀ ẹ̀dá.” Suuratul Baqara: 285 Allah tun sọ pe:

{قُلۡ ءَامَنَّا بِٱللَّهِ وَمَآ أُنزِلَ عَلَيۡنَا وَمَآ أُنزِلَ عَلَىٰٓ إِبۡرَٰهِيمَ وَإِسۡمَٰعِيلَ وَإِسۡحَٰقَ وَيَعۡقُوبَ وَٱلۡأَسۡبَاطِ وَمَآ أُوتِيَ مُوسَىٰ وَعِيسَىٰ وَٱلنَّبِيُّونَ مِن رَّبِّهِمۡ لَا نُفَرِّقُ بَيۡنَ أَحَدٖ مِّنۡهُمۡ وَنَحۡنُ لَهُۥ مُسۡلِمُونَ}

Sọ pé: “A gbàgbọ́ nínú Allāhu àti ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún wa pẹ̀lú ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm, ’Ismọ̄‘īl, ’Ishāḳ, Ya‘ḳūb, àti àwọn àrọ́mọdọ́mọ (rẹ̀. A gbàgbọ́ nínú) ohun tí Wọ́n fún (Ànábì) Mūsā àti ‘Īsā àti àwọn Ànábì láti ọ̀dọ̀ Olúwa

wọn; A kò ya ẹnì kan kan sọ́tọ̀ nínú wọn. Àwa sì ni mùsùlùmí (olùjuwọ́-jusẹ̀-sílẹ̀) fún Un." Aal Im'raan/84

Eleekerin: Nini ìgbàgbọ́ si gbogbo awọn Anabi ati awon Ojise – ki ola o maa ba won – ati nini adisokan pelu wipe dajudaju gbogbo won Òjíṣẹ ni won lati odo Ọlọhun ti won n mu awon afiranse Ọlọhun ati esin Rẹ ati ofin Re de etigbo awon ijo won, Olohun ti Ọla Re ga sọ pe:

{ قُولُوا آمَنَّا بِاللَّهِ وَمَا أُنزِلَ إِلَيْنَا وَمَا أُنزِلَ إِلَىٰ إِبْرَاهِيمَ وَإِسْمَاعِيلَ وَإِسْحَاقَ وَيَعْقُوبَ وَالْأَسْبَاطِ وَمَا أُوتِيَ مُوسَىٰ وَعِيسَىٰ وَمَا أُوتِيَ النَّبِيُّونَ مِن رَّبِّهِمْ لَا نُفَرِّقُ بَيْنَ أَحَدٍ مِّنْهُمْ وَنَحْنُ لَهُ مُسْلِمُونَ }

Ẹ sọ pé: "A gbàgbọ́ nínú Allāhu àti ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún wa àti ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún (àwọn Ànábì) 'Ibrọ̄hīm, 'Ismọ̄'īl, 'Ishāƙ, Ya'ƙūb àti àwọn àrọ́mọdọ́mọ Ya'ƙūb. (A gbàgbọ́ nínú) ohun tí Wọ́n fún (àwọn Ànábì) Mūsā àti 'Īsā, àti ohun tí Wọ́n fún àwọn Ànábì (yòókù) láti ọ̀dọ̀ Olúwa wọn. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú wọn. Àwa sì ni mùsùlùmí (olùjuwọ́-jusẹ̀ sílẹ̀) fún Un." Suuratul Baqorah: 136. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ آمَنَ الرَّسُولُ بِمَا أُنزِلَ إِلَيْهِ مِن رَّبِّهِ وَالْمُؤْمِنُونَ ۚ كُلٌّ آمَنَ بِاللَّهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ لَا نُفَرِّقُ بَيْنَ أَحَدٍ مِّن رُّسُلِهِ ۚ وَقَالُوا سَمِعْنَا وَأَطَعْنَا ۖ غُفْرَانَكَ رَبَّنَا وَإِلَيْكَ الْمَصِيرُ }

Òjíṣẹ́ náà (sollalāhu 'alayhi wa sallam) gbàgbọ́ nínú ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún un láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀. Àwọn onígbàgbọ́ òdodo náà (gbàgbọ́ nínú rẹ̀). Ẹnì kọ̀ọ̀kan (wọn) gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀ àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Wọ́n sì sọ pé: "A gbọ́ (àṣẹ), a sì tẹ̀lé

(àṣẹ). À ń tọrọ àforíjìn Rẹ, Olúwa wa. Ọ̀dọ̀ Rẹ sì ni àbọ̀ ẹ̀dá.” Suuratul Baqara: 285 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ قُلْ آمَنَّا بِاللَّهِ وَمَا أُنزِلَ عَلَيْنَا وَمَا أُنزِلَ عَلَىٰ إِبْرَاهِيمَ وَإِسْمَاعِيلَ وَإِسْحَاقَ وَيَعْقُوبَ وَالْأَسْبَاطِ وَمَا أُوتِيَ مُوسَىٰ وَعِيسَىٰ وَالنَّبِيُّونَ مِن رَّبِّهِمْ لَا نُفَرِّقُ بَيْنَ أَحَدٍ مِّنْهُمْ وَنَحْنُ لَهُ مُسْلِمُونَ }

Ẹ sọ pé: “A gbàgbọ́ nínú Allāhu àti ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún wa àti ohun tí Wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún (àwọn Ànábì) ’Ibrọ̄hīm, ’Ismọ̄‘īl, ’Ishāḳ, Ya‘ḳūb àti àwọn àrọ́mọdọ́mọ Ya‘ḳūb. (A gbàgbọ́ nínú) ohun tí Wọ́n fún (àwọn Ànábì) Mūsā àti ‘Īsā, àti ohun tí Wọ́n fún àwọn Ànábì (yòókù) láti ọ̀dọ̀ Olúwa wọn. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú wọn. Àwa sì ni mùsùlùmí (olùjuwọ́-jusẹ̀ sílẹ̀) fún Un.” Aal Im’raan/84

Ati pe ki o si ni igbagbọ pelu ikẹhin wọn, Oun naa ni Muhammad Òjíṣẹ Ọlọhun, igbẹyin awọn Anabi ati awọn Òjíṣẹ– ki ike ati ola o maa ba wọn– Olohun ti Ọla Rẹ ga sọ pe:

{ إِذْ أَخَذَ ٱللَّهُ مِيثَٰقَ ٱلنَّبِيِّـۧنَ لَمَآ ءَاتَيْتُكُم مِّن كِتَٰبٍ وَحِكْمَةٍ ثُمَّ جَآءَكُمْ رَسُولٌ مُّصَدِّقٌ لِّمَا مَعَكُمْ لَتُؤْمِنُنَّ بِهِۦ وَلَتَنصُرُنَّهُۥ ۚ قَالَ ءَأَقْرَرْتُمْ وَأَخَذْتُمْ عَلَىٰ ذَٰلِكُمْ إِصْرِى ۖ قَالُوٓا۟ أَقْرَرْنَا ۚ قَالَ فَٱشْهَدُوا۟ وَأَنَا۠ مَعَكُم مِّنَ ٱلشَّٰهِدِينَ}

(Ẹ rántí) nígbà tí Allāhu gba àdéhùn lọ́wọ́ àwọn Ànábì pé: “(Ẹ lo) èyí tí Mo bá fun yín nínú Tírà àti ìjìnlẹ̀ òye (ìyẹn, sunnah ẹnì kọ̀ọ̀kan wọn). Lẹ́yìn náà, Òjíṣẹ́ kan (ìyẹn, Ànábì Muhammad s.a.w.) yóò dé ba yín; ó máa fi èyí t’ó jẹ́ òdodo rinlẹ̀ nípa èyí t’ó wà pẹ̀lú yín. Nítorí náà, ẹ gbọ́dọ̀ gbà á gbọ́, ẹ sì gbọ́dọ̀ ràn án lọ́wọ́.” (Allāhu) sọ pé: “Ǹjẹ́ ẹ gbà? Ṣé ẹ sì máa lo àdéhùn Mi yìí?” Wọ́n sọ pé: “A gbà.” (Allāhu) sọ pé:

"Nítorí náà, ẹ jẹ́rìí sí (àdéhùn náà). Èmi ń bẹ pẹ̀lú yín nínú àwọn Olùjẹ́rìí." Aal Im’raan/81

Esin Islaam se ni dandan nini igbagbo si gbogbo awon Anabi ati awon Ojise lapapo, o si tun se e ni dandan nini igbagbọ si ikẹhin wọn, oun naa ni Òjíṣẹ ti ń ṣe Muhammad– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– Ọlọhun ti Ola Re ga so pe:

{قُلْ يَا أَهْلَ الْكِتَابِ لَسْتُمْ عَلَىٰ شَيْءٍ حَتَّىٰ تُقِيمُوا التَّوْرَاةَ وَالْإِنجِيلَ وَمَا أُنزِلَ إِلَيْكُم مِّن رَّبِّكُمْ}

Sọ pé: “Ẹ̀yin ahlul-kitāb, ẹ ò rí kiní kan ṣe (nínú ẹ̀sìn) títí ẹ máa fi lo at-Taorāh àti al-’Injīl àti ohun tí A sọ̀kalẹ̀ fun yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín (ìyẹn, al-Ḱur’ān).” Suuratul Ma’idah: 68. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{قُلْ يَا أَهْلَ الْكِتَابِ تَعَالَوْا إِلَىٰ كَلِمَةٍ سَوَاءٍ بَيْنَنَا وَبَيْنَكُمْ أَلَّا نَعْبُدَ إِلَّا اللَّهَ وَلَا نُشْرِكَ بِهِ شَيْئًا وَلَا يَتَّخِذَ بَعْضُنَا بَعْضًا أَرْبَابًا مِّن دُونِ اللَّهِ ۚ فَإِن تَوَلَّوْا فَقُولُوا اشْهَدُوا بِأَنَّا مُسْلِمُونَ}

Sọ pé: “Ẹ̀yin ahlu-l-kitāb, ẹ wá síbi ọ̀rọ̀ kan t’ó dọ́gba láàárin àwa àti ẹ̀yin, pé a ò níí jọ́sìn fún ẹnì kan àfi Allāhu. A ò sì níí fi kiní kan wá akẹgbẹ́ fún Un. Àti pé apá kan wa kò níí sọ apá kan di olúwa lẹ́yìn Allāhu.” Tí wọ́n bá sì gbúnrí, ẹ sọ pé: “Ẹ jẹ́rìí pé dájúdájú mùsùlùmí ni àwa.” Aal Im’raan/64

Ati pe ẹnikẹni ti o ba se aìgbàgbọ́ si Anabi kan, o ti se aigbagbo si gbogbo awon Anabi ati awon Ojise – ki ola o maa ba won – tori naa ni Olohun fi so ni Eni ti O n fun wa ni iro nipa idajo Re lori ijo Anabi Nuuh – ki ola o maa ba a:

{كَذَّبَتْ قَوْمُ نُوحٍ الْمُرْسَلِينَ}

Ìjọ (Ànábì) Nūh pe àwọn Òjíṣẹ́ ní òpùrọ́. Suuratush Shuarah: 105. Ohun ti a si mo ni wipe Anabi Nuuh– ki ola o maa ba a– ojise kan ko saaju re, toun ti bee nigbati awon ijo re pe e ni iro, ipe e ni iro won yii je ipe gbogbo awon Anabi ati Ojise ni iro; nitoripe ipepe won eyokan ni ogongo ti won si n pepe si ẹyokan ni.

Eleekarun-un: Nini ìgbàgbọ́ si ọjọ ikẹhin, oun naa ni ọjọ igbedide, ni ipari ile-aye yii, Olohun yoo pa Malaika to n jẹ Isroofiil – ki ola o maa ba a- ni ase ki o fun feere kíkú, ti gbogbo nkan ti Olohun ba si fe yoo si ku, Olohun ti Ọla Rẹ ga sọ pe:

{ وَنُفِخَ فِي الصُّورِ فَصَعِقَ مَن فِي السَّمَاوَاتِ وَمَن فِي الْأَرْضِ إِلَّا مَن شَاءَ اللَّهُ ۖ ثُمَّ نُفِخَ فِيهِ أُخْرَىٰ فَإِذَا هُمْ قِيَامٌ يَنظُرُونَ }

Wọ́n á fọn fèrè oníwo fún ikú. Àwọn t’ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ sì máa kú àfi ẹni tí Allāhu bá fẹ́. Lẹ́yìn náà, wọ́n máa fọn ọ́n ní ẹ̀ẹ̀ keji, nígbà náà wọ́n máa wà ní ìdìde. Wọn yó sì máa wò sùn. Suuratu Zumar: 68. Ati pe ti gbogbo awon ti o wa ni awon sanmo ati awon ti won wa ni ile ba ti ku, dajudajun Olohun yoo ka awon sanmo ati ile ko gegebi o se wa ninu gbolohun Re ti O wipe:

{يَوْمَ نَطْوِي السَّمَاءَ كَطَيِّ السِّجِلِّ لِلْكُتُبِ ۚ كَمَا بَدَأْنَا أَوَّلَ خَلْقٍ نُّعِيدُهُ ۚ وَعْدًا عَلَيْنَا ۚ إِنَّا كُنَّا فَاعِلِينَ }

(Ọjọ́ náà ni) ọjọ́ tí A máa ká sánmọ̀ bí kíká ewé tírà. Gẹ́gẹ́ bí A ti ṣe bẹ̀rẹ̀ ìṣẹ̀dá ẹ̀dá ní ìbẹ̀rẹ̀ pẹ̀pẹ̀ (ibẹ̀ náà ni) A óò dá a padà sí. (Ó jẹ́) àdéhùn tí A ṣe. Dájúdájú Àwa máa ṣe bẹ́ẹ̀. Suuratul Anbiyaah: 104 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ وَمَا قَدَرُوا اللَّهَ حَقَّ قَدْرِهِ وَالْأَرْضُ جَمِيعًا قَبْضَتُهُ يَوْمَ الْقِيَامَةِ وَالسَّمَاوَاتُ مَطْوِيَّاتٌ بِيَمِينِهِ ۚ سُبْحَانَهُ وَتَعَالَىٰ عَمَّا يُشْرِكُونَ }

Wọn kò bu iyì fún Allāhu bí ó ṣe tọ́ láti bu iyì fún Un. Gbogbo ilẹ̀ pátápátá sì ni (Allāhu) máa fọwọ́ ara Rẹ̀ gbámú ní Ọjọ́ Àjíǹde. Ó sì máa fi ọwọ́ ọ̀tún Rẹ̀ ká sánmọ̀ kóróbójó. Mímọ́ ni fún Un. Ó sì ga tayọ ǹǹkan tí wọ́n ń fi ṣẹbọ sí I. Suuratuz Zumar: 67 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«يَطْوِي اللهُ عَزَّ وَجَلَّ السَّمَاوَاتِ يَوْمَ الْقِيَامَةِ ثُمَّ يَأْخُذُهُنَّ بِيَدِهِ الْيُمْنَى ثُمَّ يَقُولُ: أَنَا الْمَلِكُ أَيْنَ الْجَبَّارُونَ؟ أَيْنَ الْمُتَكَبِّرُونَ. ثُمَّ يَطْوِي الْأَرَضِينَ بِشِمَالِهِ ثُمَّ يَقُولُ: أَنَا الْمَلِكُ أَيْنَ الْجَبَّارُونَ؟ أَيْنَ الْمُتَكَبِّرُونَ؟»

Alloohu– ti O biyi ti O gbonngbon– yoo ka awon sanmo ni ojo igbedide kóróbójó, leyin naa yoo gba won mu pelu owo otun Re, leyin naa ni yoo wa so pe: Emi ni Oba Onikapa gbogbo nkan, nibo ni awon afipamuni-aye wa? Nibo ni awon oluse-igberaga wa? Leyin naa yoo gba awon ile mu pelu owo alaafia Re, leyin naa yoo wa so pe: Emi ni Oba Onikapa gbogbo nkan, nibo ni awon afipamuni-aye wa? Nibo ni awon oluse-igberaga wa? Muslim ni o gba a wa.

Leyin naa Olohun yoo pa Malaika ni ase ki o fọn feere ni eekeji, nigba naa ni won yoo dide ti won yoo si maa wo sun, Olohun ti Ola Re ga sọ pe:

{ ثُمَّ نُفِخَ فِيهِ أُخْرَىٰ فَإِذَا هُمْ قِيَامٌ يَنظُرُونَ}

Lẹ́yìn náà, wọ́n máa fọn ọ́n ní ẹ̀ẹ̀ keji, nígbà náà wọ́n máa wà ní ìdìde. Wọn yó sì máa wò sùn. Suuratu Zumar: 68. Nigbati Ọlọhun ba gbe awọn ẹda dide, yoo ko wọn jọ fun ìṣirò. Ọlọhun- ti Ọla Rẹ ga- sọ pe:

{يَوْمَ تَشَقَّقُ الْأَرْضُ عَنْهُمْ سِرَاعًا ذَٰلِكَ حَشْرٌ عَلَيْنَا يَسِيرٌ}

(Rántí) ọjọ́ tí ilẹ̀ yóò fàya pẹ́rẹpẹ̀rẹ mọ́ wọn lára, (tí wọn yóò máa) yára (jáde láti inú ilẹ̀). Ìyẹn ni àkójọ t'ó rọrùn fún Wa. Suuratu Qof: 44. Allah- ti ọla Rẹ ga julọ-tun sọ pe:

{يَوْمَ هُم بَارِزُونَ ۖ لَا يَخْفَىٰ عَلَى اللَّهِ مِنْهُمْ شَيْءٌ ۚ لِّمَنِ الْمُلْكُ الْيَوْمَ ۖ لِلَّهِ الْوَاحِدِ الْقَهَّارِ }

Ní ọjọ́ tí wọn yóò yọ jáde (láti inú sàréè), kiní kan kò sì níí pamọ́ nípa wọn fún Allāhu. (Allāhu yó sì sọ pé): "Ti ta ni ìjọba ní ọjọ́ òní? Ti Allāhu, Ọ̀kan ṣoṣo, Olùborí ni." Suratu Ghafir: 16 Ati pe ni ọjọ yii, Ọlọhun yóò se ìṣirò gbogbo eniyan patapata, yoo si gba ẹsan fun ẹni ti wọn bosi lowo ẹni ti o bo o si, yoo wa san gbogbo eniyan ni ẹsan pẹlu nnkan ti o se, Ọlọhun- ti Ọla Re ga- sọ pe:

{ الْيَوْمَ تُجْزَىٰ كُلُّ نَفْسٍ بِمَا كَسَبَتْ ۚ لَا ظُلْمَ الْيَوْمَ ۚ إِنَّ اللَّهَ سَرِيعُ الْحِسَابِ}

Ní òní ni A óò san ẹ̀mí kọ̀ọ̀kan ní ẹ̀san ohun tí ó ṣe níṣẹ́. Kò sì sí àbòsí kan ní òní. Dájúdájú Allāhu ni Olùyára níbi ìṣírò-iṣẹ́. Suuratu Gaafir: 17. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{إِنَّ اللَّهَ لَا يَظْلِمُ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ ۖ وَإِن تَكُ حَسَنَةً يُضَاعِفْهَا وَيُؤْتِ مِن لَّدُنْهُ أَجْرًا عَظِيمًا}

Dájúdájú Allāhu kò níí ṣàbòsí òdíwọ̀n ọmọ iná-igún. Tí ó bá jẹ iṣẹ́ rere, Ó máa ṣàdìpèlé (ẹ̀san) rẹ̀. Ó sì máa fún (olùṣe rere) ní ẹ̀san ńlá láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀. Suuratun Nisai: 40. Ọlọhun- ti Ọla Rẹ ga- tun sọ pe: (Nítorí náà, ẹni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere ní òdíwọ̀n ọmọ iná-igún, ó máa rí i.)

{وَمَن يَعْمَلْ مِثْقَالَ ذَرَّةٍ شَرًّا يَرَهُ (8)}

Ẹni tí ó bá sì ṣe iṣẹ́ aburú ní òdíwọ̀n ọmọ iná-igún, ó máa rí i. Suuratu Zalzalah: 7-8. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَنَضَعُ الْمَوَازِينَ الْقِسْطَ لِيَوْمِ الْقِيَامَةِ فَلَا تُظْلَمُ نَفْسٌ شَيْئًا ۖ وَإِن كَانَ مِثْقَالَ حَبَّةٍ مِّنْ خَرْدَلٍ أَتَيْنَا بِهَا ۗ وَكَفَىٰ بِنَا حَاسِبِينَ}

A máa gbé àwọn òṣùwọ̀n déédé kalẹ̀ ní Ọjọ́ Àjíǹde. Nítorí náà, wọn kò níí ṣe àbòsí kiní kan fún ẹ̀mí kan. Kí (iṣẹ́) jẹ́ ìwọ̀n èso kardal (bín-íntín), A máa mú un wá. A sì tó ní Olùṣírò. Suuratul Anbiyaah: 47.

Leyin igbedide ati isiro, esan yoo sele, eni ti o ba ṣe daadaa, idekun gbere ti ko nii kúrò ni n be fun un, ẹni tí o ba se aburu ati aigbagbo, iya n be fun un. Olohun ti ola Re ga so pe:

{الْمُلْكُ يَوْمَئِذٍ لِّلَّهِ يَحْكُمُ بَيْنَهُمْ ۚ فَالَّذِينَ آمَنُوا وَعَمِلُوا الصَّالِحَاتِ فِي جَنَّاتِ النَّعِيمِ (56) وَالَّذِينَ كَفَرُوا وَكَذَّبُوا بِآيَاتِنَا فَأُولَٰئِكَ لَهُمْ عَذَابٌ مُّهِينٌ (57) }

Gbogbo ìjọba ọjọ́ yẹn ń jẹ́ ti Allāhu tí Ó máa ṣèdájọ́ láàārin wọn. Nítorí náà, àwọn t’ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí wọ́n sì ṣe àwọn iṣẹ́ rere, (wọn yóò wà) nínú àwọn Ọgbà Ìdẹ̀ra.

Àwọn t’ó sì ṣàì gbàgbọ́, tí wọ́n tún pe àwọn āyah Wa nírọ́; àwọn wọ̀nyẹn ni ìyà tí í yẹpẹrẹ ẹ̀dá sì wà fún. Suuratul Hajj: 56-57. Ati pe a maa lọ mo wipe kani isemi ile-aye je opin ni; isemi ati bibe o ba je iranu ponnbele. Olohun ti Ola Re ga so pe:

{ أَفَحَسِبْتُمْ أَنَّمَا خَلَقْنَاكُمْ عَبَثًا وَأَنَّكُمْ إِلَيْنَا لَا تُرْجَعُونَ }

Ṣé ẹ lérò pé A kàn ṣẹ̀dá yín fún ìranù ni, àti pé dájúdájú wọn ò níí da yín padà sọ́dọ̀ Wa?” Suuratul Muh’minuun: 115.

Ẹlẹ̀ẹ̀kẹfà: Nini igbagbo si kadara, oun ni wipe o je dandan nini igbagbo wipe Olohun ti ni imo nipa nkan ti o ti sele, ati nkan ti n sele lowo, ati nkan ti yoo pada sele ninu aye yii, ati pe Olohun ti kọ gbogbo nkan siwaju ki O to da awon sanmo ati ile. Olohun ti Ola Re ga so pe:

{ وَعِندَهُ مَفَاتِحُ الْغَيْبِ لَا يَعْلَمُهَا إِلَّا هُوَ ۚ وَيَعْلَمُ مَا فِي الْبَرِّ وَالْبَحْرِ ۚ وَمَا تَسْقُطُ مِن وَرَقَةٍ إِلَّا يَعْلَمُهَا وَلَا حَبَّةٍ فِي ظُلُمَاتِ الْأَرْضِ وَلَا رَطْبٍ وَلَا يَابِسٍ إِلَّا فِي كِتَابٍ مُّبِينٍ }

Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni àwọn kọ́kọ́rọ́ ìkọ̀kọ̀ wà. Kò sí ẹni t’ó nímọ̀ rẹ̀ àfi Òun. Ó nímọ̀ ohun tí ń bẹ nínú ilẹ̀ àti odò. Ewé kan kò sì níí já bọ́ àfi kí Ó nímọ̀ rẹ̀. Kò sì sí kóró èso kan nínú òkùnkùn (inú) ilẹ̀, kò sí ohun tútù tàbí gbígbẹ kan àfi kí ó wà nínú àkọsílẹ̀ t’ó yanjú. Suuratul An’aam: 59. Ati pe dajudaju imo Olohun ti rokirika gbogbo nkan. Olohun ti Ola Re ga pe:

{اللَّهُ الَّذِي خَلَقَ سَبْعَ سَمَاوَاتٍ وَمِنَ الْأَرْضِ مِثْلَهُنَّ يَتَنَزَّلُ الْأَمْرُ بَيْنَهُنَّ لِتَعْلَمُوا أَنَّ اللَّهَ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ قَدِيرٌ وَأَنَّ اللَّهَ قَدْ أَحَاطَ بِكُلِّ شَيْءٍ عِلْمًا}

Allāhu ni Ẹni tí Ó ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ méje àti ilẹ̀ ní (òǹkà) irú rẹ̀. Àṣẹ ń sọ̀kalẹ̀ láààrin wọn nítorí kí ẹ lè mọ̀ pé dájúdájú Allāhu ni Alágbára lórí gbogbo ǹǹkan. Àti pé dájúdájú Allāhu fi ìmọ̀ rọ̀gbà yí gbogbo ǹǹkan ká. Suuratu Tolaq: 12. Ati pe dajudaju alamori Kankan o ni sele ni aye yii ayaafi ki Olohun ti gbero re ki O si ti fẹẹ, ki O si ti seda re, ki O si ti se awon okunfa re ni irorun. Olohun ti Ọla Rẹ ga sọ pe:

{الَّذِي لَهُ مُلْكُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَلَمْ يَتَّخِذْ وَلَدًا وَلَمْ يَكُن لَّهُ شَرِيكٌ فِي الْمُلْكِ وَخَلَقَ كُلَّ شَيْءٍ فَقَدَّرَهُ تَقْدِيرًا }

(Òun ni) Ẹni tí Ó ni ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Kò mú ẹnì kan kan ní ọmọ. Kò sí akẹgbẹ́ fún Un nínú ìjọba (Rẹ̀). Ó dá gbogbo n̄ǹkan. Ó sì yan òdíwọ̀n (ìrísí, ìṣẹ̀mí àti àyànmọ́) fún un níwọ̀n-níwọ̀n. Suratul Furqan: 2 O si n be fun Un nibi iyen ijinle oye ti o peye, eleyi ti imo omoniyan o le de ibe. Olohun ti Ola Re ga so pe:

{حِكْمَةٌ بَالِغَةٌ ۖ فَمَا تُغْنِ النُّذُرُ}

Ìjìnlẹ̀ òye t’ó péye ni; ṣùgbọ́n àwọn ìkìlọ̀ náà kò rọ̀ wọ́n lọ́rọ̀. suuratul Qomar: 5. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَهُوَ الَّذِي يَبْدَأُ الْخَلْقَ ثُمَّ يُعِيدُهُ وَهُوَ أَهْوَنُ عَلَيْهِ وَلَهُ الْمَثَلُ الْأَعْلَىٰ فِي السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَهُوَ الْعَزِيزُ الْحَكِيمُ}

Òun ni Ẹni tí Ó ń bẹ̀rẹ̀ ẹ̀dá dídá. Lẹ́yìn náà, Ó máa dá a padà (sípò alàààyè fún àjíǹde). Ó sì rọrùn jùlọ fún Un (láti ṣe bẹ́ẹ̀). TiRẹ̀ ni ìròyìn t’ó ga jùlọ nínú àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Òun sì ni Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Suuratu Ruum: 27. Ọlọhun Ọba si tun royin ara Rẹ̀ pẹlu ọgbọ́n, O si pe ara Rẹ ni Ọlọ́gbọ́n. Ọlọhun ti Ọla Rẹ ga sọ pe:

{شَهِدَ اللَّهُ أَنَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ وَالْمَلَائِكَةُ وَأُولُو الْعِلْمِ قَائِمًا بِالْقِسْطِ ۚ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ الْعَزِيزُ الْحَكِيمُ}

Allāhu jẹ́rìí pé dájúdájú kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Àwọn mọlāika àti onímọ̀ ẹ̀sìn (tún jẹ́rìí bẹ́ẹ̀.), Allāhu ni Onídéédé. Kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Aal Im’raan/18 Ọlọhun ti Ọla Rẹ ga si tun sọ ni Ẹni ti O n fun wa ni iro nipa

Anabi Isa– ki ọla Ọlọhun maa ba a– wipe yóò ba Ọlọhun sọ̀rọ̀ ni ọjọ igbedide ni ẹni ti yoo maa sọ pe:

{إِن تُعَذِّبْهُمْ فَإِنَّهُمْ عِبَادُكَ ۖ وَإِن تَغْفِرْ لَهُمْ فَإِنَّكَ أَنتَ الْعَزِيزُ الْحَكِيمُ}

Tí O bá jẹ wọ́n níyà, dájúdájú ẹrú Rẹ ni wọ́n. Tí O bá sì forí jìn wọ́n, dájúdájú Ìwọ, Ìwọ ni Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Suuratul Maa'idah: 118. Olohun ti ola Re ga tun so fun Anabi Musa– ki ola Olohun maa ba a– nígbà ti O (Alloohu) pe e (Musa) ti o (Musa) wa ni ẹgbẹ òkè Tuur:

{يَا مُوسَىٰ إِنَّهُ أَنَا اللَّهُ الْعَزِيزُ الْحَكِيمُ}

Mūsā, dájúdájú Èmi ni Allāhu, Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Suuratu Naml: 9.

O si tun royin Al-Qur'aan ti o tobi pelu ọgbọn . Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{الر ۚ كِتَابٌ أُحْكِمَتْ آيَاتُهُ ثُمَّ فُصِّلَتْ مِن لَّدُنْ حَكِيمٍ خَبِيرٍ}

'Alif lām rọ̄. (Èyí ni) Tírà tí wọ́n ti to àwọn āyah inú rẹ̀ ní àtògún régé, lẹ́yìn náà wọ́n ṣàlàyé rẹ̀ yékéyéké láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́gbọ́n, Alámọ̀tán. Suuratu Huud: 1. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ ذَٰلِكَ مِمَّا أَوْحَىٰ إِلَيْكَ رَبُّكَ مِنَ الْحِكْمَةِ ۗ وَلَا تَجْعَلْ مَعَ اللَّهِ إِلَٰهًا آخَرَ فَتُلْقَىٰ فِي جَهَنَّمَ مَلُومًا مَّدْحُورًا}

Ìyẹn wà nínú ohun tí Olúwa rẹ fi ránṣẹ́ sí ọ nínú ìjìnlẹ̀ ọgbọ́n (al-Ƙur'ān). Má ṣe mú ọlọ́hun mìíràn mọ́ Allāhu kí wọ́n má baà jù ọ́ sínú iná Jahanamọ ní ẹni àbùkù, ẹni ẹ̀kọ̀. Suuratul Is'raah: 39.

## 22. Àti pé awon Anabi Olohun won ti so won kuro nibi sise asise – ki ola o

**maa ba won – nibi nkan ti won n mu de etigbo awon eeyan nipa Olohun, won si tun so won kuro nibi gbogbo nkan ti o ba ti tako laakaye tabi nkan ti iwa to dáa ba tako, ati pe awon Anabi Olohun won je eniti a ti la mimu awon ase Olohun de odo awon ẹrú Re bọ lọrun, ati pe awon Anabi Olohun ko si nkankan fun won ninu awon ìròyìn jijẹ oluwa tabi ẹni tí ó lẹ́tọ̀ọ́ si ìjọsìn; bi kii se pe abara ni won gegebi awon abara yoku ti Olohun si n mu imisi awon oro Re wa ba won.**

Ati pe awon Anabi Olohun won ti so won kuro nibi sise asise– ki ola o maa ba won– nibi nkan ti won n mu de etigbọ awon eeyan nipa Olohun; toripe dajudaju Olohun maa n ṣẹsa àwọn ti o ba dáa jù nínú àwọn ẹ̀dá Rẹ lati mu oro Re de etigbo awon eeyan. Olohun ti ola Re ga so pe:

{اللَّهُ يَصْطَفِي مِنَ الْمَلَائِكَةِ رُسُلًا وَمِنَ النَّاسِ ۚ إِنَّ اللَّهَ سَمِيعٌ بَصِيرٌ}

Allāhu l'Ó ń ṣa àwọn kan lẹ́ṣà (láti jẹ́) Òjíṣẹ́ nínú àwọn mọlāika àti nínú àwọn èniyàn. Dájúdájú Allāhu ni Olùgbọ́, Olùríran. Suuratul Hajj: 75. Allah ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ إِنَّ ٱللَّهَ ٱصۡطَفَىٰٓ ءَادَمَ وَنُوحٗا وَءَالَ إِبۡرَٰهِيمَ وَءَالَ عِمۡرَٰنَ عَلَى ٱلۡعَٰلَمِينَ}

Dájúdájú Allāhu ṣa Ādam, Nūh, ará ilé ’Ibrọ̄hīm àti ará ilé ‘Imrọ̄n lẹ́ṣà lórí àwọn ẹ̀dá (àsìkò tiwọn). Aal-Imraan 33 Allah tun sọ pe:

{ قَالَ يَٰمُوسَىٰٓ إِنِّي ٱصۡطَفَيۡتُكَ عَلَى ٱلنَّاسِ بِرِسَٰلَٰتِي وَبِكَلَٰمِي فَخُذۡ مَآ ءَاتَيۡتُكَ وَكُن مِّنَ ٱلشَّٰكِرِينَ}

(Allāhu) sọ pé: "Mūsā, dájúdájú Èmi ṣà ọ́ lẹ́ṣà lórí àwọn ènìyàn pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ Mi àti ọ̀rọ̀ Mi. Nítorí náà, gbá ohun tí Mo fún ọ mú. Kí o sì wà nínú àwọn olùdúpẹ́." Suuratul A’arof: 144. Ati pe awon Ojise – ki ike ati ola maa ba won – mo wipe nkan ti o n so kale wa ba won, imisi ti Olohun ni, won si tun maa n ri awon Malaaika nígbà ti won ba n sokale pelu imisi naa. Olohun ti ola Re ga so pe:

{ عالِمُ الْغَيْبِ فَلَا يُظْهِرُ عَلَىٰ غَيْبِهِ أَحَدًا (26) إِلَّا مَنِ ارْتَضَىٰ مِن رَّسُولٍ فَإِنَّهُ يَسْلُكُ مِن بَيْنِ يَدَيْهِ وَمِنْ خَلْفِهِ رَصَدًا (27) لِّيَعْلَمَ أَن قَدْ أَبْلَغُوا رِسَالَاتِ رَبِّهِمْ وَأَحَاطَ بِمَا لَدَيْهِمْ وَأَحْصَىٰ كُلَّ شَيْءٍ عَدَدًا (28)}

Onímọ̀-ìkọ̀kọ̀, kò sì fi (ìmọ̀) ìkọ̀kọ̀ Rẹ̀ han ẹni kan

àyàfi ẹni tí Ó ṣàlẹ́ṣà t’ó jẹ́ Òjíṣẹ́. Dájúdájú Ó ń mú ẹ̀ṣọ́ kan rìn níwájú Òjíṣẹ́ náà àti lẹ́yìn rẹ̀

nítorí kí Ó lè ṣàfi hàn pé wọ́n ti jẹ́ àwọn iṣẹ́ Olúwa wọn. Àti pé Allāhu fi ìmọ̀ rọkiri ká ohun tí ń bẹ lọ́dọ̀ wọn. Ó sì ṣọ́ òǹkà gbogbo ǹǹkan. Suuratul Jinn: 26-28. Olohun si tun pa won ni ase pelu mimu oro Re de etigbo awon eeyan. Olohun ti ola Re ga so pe:

{يَا أَيُّهَا الرَّسُولُ بَلِّغْ مَا أُنزِلَ إِلَيْكَ مِن رَّبِّكَ ۖ وَإِن لَّمْ تَفْعَلْ فَمَا بَلَّغْتَ رِسَالَتَهُ ۚ وَاللَّهُ يَعْصِمُكَ مِنَ النَّاسِ ۗ إِنَّ اللَّهَ لَا يَهْدِي الْقَوْمَ الْكَافِرِينَ}

Ìwọ Òjíṣẹ́, fi gbogbo ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún ọ láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ jíṣẹ́. Tí o ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, o ò jíṣẹ́ pé. Allāhu

yó sì dáàbò bò ọ́ lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn. Dájúdájú Allāhu kò níí fi ọ̀nà mọ ìjọ aláìgbàgbọ́ (láti ṣe ọ́ ní aburú). Al-Maaidah 67 Allah tun sọ pe:

{رُّسُلٗا مُّبَشِّرِينَ وَمُنذِرِينَ لِئَلَّا يَكُونَ لِلنَّاسِ عَلَى ٱللَّهِ حُجَّةُۢ بَعۡدَ ٱلرُّسُلِۚ وَكَانَ ٱللَّهُ عَزِيزًا حَكِيمٗا}

(A ṣe wọ́n ní) Òjíṣẹ́, oníròó ìdùnnú àti olùkìlọ̀ nítorí kí àwíjàre má lè wà fún àwọn ènìyàn lọ́dọ̀ Allāhu lẹ́yìn (tí) àwọn Òjíṣẹ́ (ti jíṣẹ́). Allāhu sì ń jẹ́ Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Suuratun Nisai: 165.

Awon Ojise Olohun – ki ike ati ola maa ba won – maa n bẹru Olohun ni iberu ti o ni agbara, won si maa n paya Re, won o lee fi kun awon oro Re, won o si yo kuro ninu re, Olohun ti ola Re ga so pe:

{ وَلَوْ تَقَوَّلَ عَلَيْنَا بَعْضَ الْأَقَاوِيلِ (44) لَأَخَذْنَا مِنْهُ بِالْيَمِينِ (45) ثُمَّ لَقَطَعْنَا مِنْهُ الْوَتِينَ (46) فَمَا مِنكُم مِّنْ أَحَدٍ عَنْهُ حَاجِزِينَ (47)}

Tí ó bá jẹ́ pé (Ànábì) dá àdápa apá kan ọ̀rọ̀ náà mọ́ Wa ni,

Àwa ìbá gbá a mú lọ́wọ́ ọ̀tún.

Lẹ́yìn náà, Àwa ìbá já isan ọrùn rẹ̀.

Kò sì sí ẹnì kan nínú yín tí ó máa gbà á sílẹ̀ lọ́wọ́ (Wa). Suuratul Aaqqah: 44-47. Ibnu Katheer– ki Olohun ke e– sọ pe: Tí ó bá jẹ́ pé (Ànábì) dá àdápa apá kan mọ́ Wa ni {iyen ni wipe: Muhammad – ki ike ati ola Olohun maa ba a – ti o ba ri bi won se n lero ni, pe o je eniti n paro mo Wa, ti o wa se alekun nibi ise ti A fi ran an tabi o yo kuro ni inu re, tabi ki o so nkankan lati odo ara re, ki o wa se afiti re si odo Wa – leyiti ko si ri bi won se lero – A o ba kanju fi iya je e, iyen ni o faa ti O fi so pe}: Àwa ìbá gbá a mú lọ́wọ́ọ̀tún. {won

so pe: itumo re ni wipe, A maa fi ìyà jẹẹ pẹ̀lú apa ọtun; toripe ìyẹn le gan ni ifiyajeni, awon kan ni: Itumo re ni wipe A máa gba a mu pelu owo otun re. Allah tun sọ pe:

{وَإِذۡ قَالَ ٱللَّهُ يَٰعِيسَى ٱبۡنَ مَرۡيَمَ ءَأَنتَ قُلۡتَ لِلنَّاسِ ٱتَّخِذُونِي وَأُمِّيَ إِلَٰهَيۡنِ مِن دُونِ ٱللَّهِۖ قَالَ سُبۡحَٰنَكَ مَا يَكُونُ لِيٓ أَنۡ أَقُولَ مَا لَيۡسَ لِي بِحَقٍّۚ إِن كُنتُ قُلۡتُهُۥ فَقَدۡ عَلِمۡتَهُۥۚ تَعۡلَمُ مَا فِي نَفۡسِي وَلَآ أَعۡلَمُ مَا فِي نَفۡسِكَۚ إِنَّكَ أَنتَ عَلَّٰمُ ٱلۡغُيُوبِ . مَا قُلۡتُ لَهُمۡ إِلَّا مَآ أَمَرۡتَنِي بِهِۦٓ أَنِ ٱعۡبُدُواْ ٱللَّهَ رَبِّي وَرَبَّكُمۡۚ وَكُنتُ عَلَيۡهِمۡ شَهِيدٗا مَّا دُمۡتُ فِيهِمۡۖ فَلَمَّا تَوَفَّيۡتَنِي كُنتَ أَنتَ ٱلرَّقِيبَ عَلَيۡهِمۡۚ وَأَنتَ عَلَىٰ كُلِّ شَيۡءٖ شَهِيدٌ}

(Rántí) nígbà tí Allāhu sọ pé: “‘Īsā ọmọ Mọryam, ṣé ìwọ l’o sọ fún àwọn ènìyàn pé: "Ẹ mú èmi àti ìyá mi ní ọlọ́hun méjì tí ẹ óò máa jọ́sìn fún lẹ́yìn Allāhu?" Ó sọ pé: "Mímọ́ ni fún Ọ, kò tọ́ fún mi láti sọ ohun tí èmi kò lẹ́tọ̀ọ́ (sí láti sọ). Tí mo bá sọ bẹ́ẹ̀, O kúkú ti mọ̀. O mọ ohun tí ń bẹ nínú ẹ̀mí mi. Ǹg ò sì mọ ohun tí ń bẹ nínú ẹ̀mí Rẹ. Dájúdájú Ìwọ ni Onímọ̀ nípa àwọn ìkọ̀kọ̀. Èmi kò sọ ohun kan fún wọn bí kò ṣe ohun tí O pa mí láṣẹ rẹ̀ pé: "Ẹ jọ́sìn fún Allāhu, Olúwa mi àti Olúwa yín." Mo sì jẹ́ ẹlẹ́rìí lórí wọn níwọ̀n ìgbà tí mò ń bẹ láàárin wọn. Ṣùgbọ́n nígbà tí O gbà mí kúrò lọ́wọ́ wọn, Ìwọ ni Olùṣọ́ lórí wọn. Ìwọ sì ni Arínú-róde gbogbo ǹǹkan Suuratul Maaidah 116-117

Ninu ola Olohun ti o se fun awon Anabi Re ati awon Ojise Re – ki ike ati ola ki o maa ba won – ni pe Olohun fi ẹsẹ won rinle nibi mimu awon oro Re de etigbo awon eeyan. Olohun ti ola Re ga so pe: Ó sọ pé:

{قَالَ إِنِّي أُشْهِدُ اللَّهَ وَاشْهَدُوا أَنِّي بَرِيءٌ مِمَّا تُشْرِكُونَ (54) مِنْ دُونِهِ فَكِيدُونِي جَمِيعًا ثُمَّ لَا تُنْظِرُونِ (55) إِنِّي تَوَكَّلْتُ عَلَى اللَّهِ رَبِّي وَرَبِّكُمْ مَا مِنْ دَابَّةٍ إِلَّا هُوَ آخِذٌ بِنَاصِيَتِهَا إِنَّ رَبِّي عَلَى صِرَاطٍ مُسْتَقِيمٍ}

Ó sọ pé: "Dájúdájú èmi ń fi Allāhu ṣe Ẹlẹ́rìí àti pé kí ẹ̀yin náà jẹ́rìí pé dájúdájú èmi yọwọ́ yọsẹ̀ nínú ohun tí ẹ̀ ń fi ṣẹbọ (54) dípò jíjọ́sìn fún Allāhu. Nítorí náà, ẹ parapọ̀ déte sí mi. Lẹ́yìn náà, kí ẹ má ṣe lọ́ mi lára (55).

Dájúdájú èmi gbáralé Allāhu, Olúwa mi àti Olúwa yín. Kò sí ẹ̀dá kan àfi kí (ó jẹ́ pé) Òun l'Ó máa fi àásó orí rẹ̀ mú un. Dájúdájú Olúwa mi wà lórí ọ̀nà tààrà. Huud 54-56 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَإِن كَادُوا لَيَفْتِنُونَكَ عَنِ الَّذِي أَوْحَيْنَا إِلَيْكَ لِتَفْتَرِيَ عَلَيْنَا غَيْرَهُ ۖ وَإِذًا لَّاتَّخَذُوكَ خَلِيلًا (73) وَلَوْلَا أَن ثَبَّتْنَاكَ لَقَدْ كِدتَّ تَرْكَنُ إِلَيْهِمْ شَيْئًا قَلِيلًا (74) إِذًا لَّأَذَقْنَاكَ ضِعْفَ الْحَيَاةِ وَضِعْفَ الْمَمَاتِ ثُمَّ لَا تَجِدُ لَكَ عَلَيْنَا نَصِيرًا (75)}

Wọ́n fẹ́ẹ̀ kó ìyọnu bá ọ nípa ǹǹkan tí A mú wá fún ọ ní ìmísí nítorí kí o lè hun ǹǹkan mìíràn t'ó yàtọ̀ sí i nípa Wa. Nígbà náà, wọn ìbá mú ọ ní ọ̀rẹ́ àyò.

Tí kò bá jẹ́ pé A fi ẹsẹ̀ rẹ rinlẹ̀ ni, dájúdájú o fẹ́ẹ̀ fi ǹǹkan díẹ̀ tẹ̀ sí ọ̀dọ̀ wọn.

Nígbà náà, Àwa ìbá jẹ́ kí o tọ́ ìlọ́po (ìyà) ìṣẹ̀mí ayé àti ìlọ́po (ìyà lẹ́yìn) ikú wò. Lẹ́yìn náà, ìwọ kò níí rí olùrànlọ́wọ́ kan tí ó máa gbà ọ́ sílẹ̀ níbi ìyà Wa. AL-ISROO 73-75 Àwọn aaya yii ati awọn eyi ti o siwaju re n jẹri, o si n tọ́ka si pe Kuraani nkan ti o sọkalẹ láti ọ̀dọ̀ Olúwa gbogbo agbalaye ni; toripe ti o ba jẹ pe odo Anọbi Muhammad – ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni o ti wa ni, i ba ti fi iru ọ̀rọ̀ ti o da oju rẹ kọọ yii sinu rẹ.Ọlọhun Ọba ti ola Rẹ ga maa n sọ àwọn ojisẹ Rẹ kuro nibi aburu àwọn eeyan, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

Ọlọhun Ọba ti ola Rẹ ga maa n sọ àwọn ojisẹ Rẹ kuro nibi aburu àwọn eeyan, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ يَا أَيُّهَا الرَّسُولُ بَلِّغْ مَا أُنزِلَ إِلَيْكَ مِن رَّبِّكَ ۖ وَإِن لَّمْ تَفْعَلْ فَمَا بَلَّغْتَ رِسَالَتَهُ ۚ وَاللَّهُ يَعْصِمُكَ مِنَ النَّاسِ ۗ إِنَّ اللَّهَ لَا يَهْدِي الْقَوْمَ الْكَافِرِينَ }

Ìwọ Òjíṣẹ́, fi gbogbo ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún ọ láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ jíṣẹ́. Tí o ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, o ò jíṣẹ́ pé. Allāhu yó sì dáàbò bò ọ́ lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn. Dájúdájú Allāhu kò níí fi ọ̀nà mọ ìjọ aláìgbàgbọ́ (láti ṣe ọ́ ní aburú). Al-Maaidah 67 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَاتْلُ عَلَيْهِمْ نَبَأَ نُوحٍ إِذْ قَالَ لِقَوْمِهِ يَا قَوْمِ إِن كَانَ كَبُرَ عَلَيْكُم مَّقَامِي وَتَذْكِيرِي بِآيَاتِ اللَّهِ فَعَلَى اللَّهِ تَوَكَّلْتُ فَأَجْمِعُوا أَمْرَكُمْ وَشُرَكَاءَكُمْ ثُمَّ لَا يَكُنْ أَمْرُكُمْ عَلَيْكُمْ غُمَّةً ثُمَّ اقْضُوا إِلَيَّ وَلَا تُنظِرُونِ }

Ka ìròyìn (Ànábì) Nūh fún wọn. Nígbà tí ó sọ fún ìjọ rẹ̀ pé: “Ẹ̀yin ènìyàn mi, tí ó bá jẹ́ pé ìdúró mi (pẹ̀lú yín) àti bí mo ṣe ń fi àwọn āyah Allāhu ṣe ìṣítí fun yín bá lágbara lára yín, nígbà náà Allāhu ni mo gbáralé. Nítorí náà, ẹ pa ìmọ̀ràn yín pọ̀, (kí ẹ sì ké pe) àwọn òrìṣà yín. Lẹ́yìn náà, kí ìpinnu ọ̀rọ̀ yín má ṣe wà ní bòńkẹ́lẹ́ láààrin yín. Lẹ́yìn náà, kí ẹ yanjú ọ̀rọ̀ mi. Kí ẹ sì má ṣe lọ́ mi lára mọ́. Yunus 71 Ọlọhun Ọba ti ola Rẹ ga sọ nípa anọbi Musa – ki àlàáfíà Ọlọhun maa ba a-pe: Àwọn méjèèjì sọ pé: Àwọn méjèèjì sọ pé: “Olúwa wa, dájúdájú àwa ń páyà pé ó má yára jẹ wá níyà tàbí pé ó má tayọ ẹnu-àlà.”

Allāhu) sọ pé: “Ẹ má ṣe páyà. Dájúdájú Èmi wà pẹ̀lú ẹ̀yin méjèèjì; Mò ń gbọ (yín), Mo sì ń ri (yín).” Too'haa 45-46 Ọlọhun Ọba ti ola Rẹ ga ṣàlàyé pe Oun maa sọ àwọn ojisẹ Rẹ kúrò lọ́wọ́ àwọn ọ̀tá wọn ti wọn ko nii ri aburu kankan fi ṣe wọn, O tun sọ pe Oun maa dáàbò bo imisi Rẹ, wọn ko ni i le e kun, wọn ko si nii din-in ku, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{إِنَّا نَحْنُ نَزَّلْنَا الذِّكْرَ وَإِنَّا لَهُ لَحَافِظُونَ}

“Dajudaju Awa (Ọlọhun Allah) ni a sọ Iranti (Alukurani) kalẹ, dajudaju awa naa ni Oludaabo bo o. Al-Hijr 9

Àwọn anọbi – ki ikẹ Ọlọhun máa bá wọn- ẹni tí a sọ kúrò níbi nkan ti o ba yapa làákàyè àti ìwà ni wọ́n, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ ni Eni ti n fọ anọbi Muhammad mọ wipe:

{ وَإِنَّكَ لَعَلَى خُلُقٍ عَظِيمٍ}

Dájúdájú ìwọ sì wà lórí ìwà àpọ́nlé. Al-Qalam 4 O tun sọ bákannáà nípa rẹ̀ pé:

{وَمَا صَاحِبُكُم بِمَجْنُون}

Àti pé ẹni yín (Ànábì Muhammad s.a.w.) kì í ṣe wèrè. At-Takwiir 22 Ìyẹn ri bẹẹ tori ki wọn le jẹ isẹ ti wọn ran wọn dáadáa, àwọn anọbi Ọlọhun si nìyí, A la jijise àwọn àṣẹ ti Ọlọhun ba pa fun awon ẹrú Rẹ bo wọn lọrun, wọn ko ni nkankan ninu ìròyìn jijẹ Oluwa tabi jijẹẹni tí o lẹtọ si ìjọsìn, abara ni wọn gẹ́gẹ́ bí àwọn abara to ku, Ọlọhun maa n fi iṣẹ iranse Rẹ ranse si wọn, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Àwọn Òjíṣẹ́ wọn sọ fún wọn pé:

{ قَالَتْ لَهُمْ رُسُلُهُمْ إِن نَّحْنُ إِلَّا بَشَرٌ مِّثْلُكُمْ وَلَٰكِنَّ اللَّهَ يَمُنُّ عَلَىٰ مَن يَشَاءُ مِنْ عِبَادِهِ ۖ وَمَا كَانَ لَنَا أَن نَّأْتِيَكُم بِسُلْطَانٍ إِلَّا بِإِذْنِ اللَّهِ ۚ وَعَلَى اللَّهِ فَلْيَتَوَكَّلِ الْمُؤْمِنُونَ}

Àwọn Òjíṣẹ́ wọn sọ fún wọn pé: “Àwa kò jẹ́ kiní kan bí kò ṣe abara bí irú yín. Ṣùgbọ́n Allāhu ń ṣoore fún ẹni tí Ó bá fẹ́ nínú àwọn ẹrúsìn Rẹ̀. Kò sì lẹ́tọ̀ọ́ fún wa láti fun yín ní ẹ̀rí kan àfi pẹ̀lú ìyọ̀nda Allāhu. Àti pé, Allāhu ni kí àwọn onígbàgbọ́ òdodo gbáralé.

Ibrahim 11 Ọlọhun tun sọ ni Eni ti n pa ojiṣẹ Rẹ Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) láṣẹ pe ki o sọfún àwọn ìjọ rẹ pe: Sọ pé:

{قُلْ إِنَّمَا أَنَا بَشَرٌ مِّثْلُكُمْ يُوحَىٰ إِلَيَّ أَنَّمَا إِلَٰهُكُمْ إِلَٰهٌ وَاحِدٌ ۖ فَمَن كَانَ يَرْجُو لِقَاءَ رَبِّهِ فَلْيَعْمَلْ عَمَلًا صَالِحًا وَلَا يُشْرِكْ بِعِبَادَةِ رَبِّهِ أَحَدًا}

Sọ pé: “Abara ni èmi bí irú yín. Wọ́n ń fi ìmísí ránṣẹ́ sí mi pé Ọlọ́hun yín, Ọlọ́hun Ọ̀kan ṣoṣo ni. Nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí ó bá ń retí ìpàdé Olúwa rẹ̀, kí ó ṣe iṣẹ́ rere. Kò sì gbọdọ̀ fi ẹnì kan kan ṣe akẹgbẹ́ níbi jíjọ́sìn fún Olúwa rẹ̀.” Al-Kahf 110

## 23. Islam n pepe si ìjọsìn fun Olohun nìkan ṣoṣo pẹ̀lú àwọn ipilẹ ìjọsìn ńlá bii: IRUN ti o se pe oun naa ni diduro ati titẹ kọkọrọ ati fifi ori kanlẹ, ati iranti Ọlọhun ati yiyin-In ati adua, ọmọniyan yoo maa ki irun naa ni ẹẹmarun ni ojoojumọ, ko si si opinya kankan laarin awọn ti wọn n ki i, ati olówò ati talika, adarí ati ẹni tí wọ́n n dari, gbogbo wọn maa to ni saafu kan naa ninu irun. Bákan náà ni ZAKAT tii ṣe odiwọn kékeré ninu dukia ni ibamu si awọn májẹ̀mú ati ipebubu tí Ọlọhun ti pebubu rẹ, ti o jẹ dandan ninu dúkìá

**àwọn ọlọrọ, ti wọn maa yọ fun awọn alaini ati awọn mìíràn ni ẹẹkan ni ọdún. Bákan náà ni AAWẸ tí í ṣe kiko ẹnu ro nibi awọn nkan tii ba aawẹ jẹ ninu oṣu Ramadan, ni eyi ti o maa n re erongba ati sùúrù ninu ẹ̀mí. Bákan náà ni HAJJ tii ṣe lílọ si ilé Oluwa ni ilu Mẹka ni ẹẹkan ni ìgbésí ayé fun ẹni tí ó bá ni ikapa. Ninu Hajj yii, gbogbo èèyàn maa ri bákan náà nibi ìdojúkọỌlọhun Adẹda, ti ko si nii si pe ẹnikan wa ni ipò tí o ga ju ẹlòmíràn lọ**

Islam n pepe si ijọsin fun Ọlọhun pẹlu awọn ìjọsìn ńlá ati nkan ti o yàtọ̀ sí i nínú àwọn ìjọsìn. Àwọn ìjọsìn ńlá yii, Ọlọhun ṣe wọn ni ọranyan lori gbogbo àwọn anọbi ati awọn ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn - eyi ti o tobi ju nínú àwọn ìjọsìn náà ni:

1. Akọkọ: IRUN, Ọlọhun ṣe e ni ọranyan lori awọn Musulumi gẹ́gẹ́ bí ó ṣe ṣe e ni ọranyan lori awọn anọbi ati awọn ojiṣẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn). Ọlọhun pa anọbi Ibrahim tii ṣe aayo Rẹ láṣẹ pe ki o fọ ilé naa mọ fun àwọn tí wọn fẹṣe tawaf ati awọn olukirun ti wọn n tẹ kọkọrọ ti wọn si n fi ori balẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَإِذْ جَعَلْنَا الْبَيْتَ مَثَابَةً لِّلنَّاسِ وَأَمْنًا وَاتَّخِذُوا مِن مَّقَامِ إِبْرَاهِيمَ مُصَلًّى ۖ وَعَهِدْنَا إِلَىٰ إِبْرَاهِيمَ وَإِسْمَاعِيلَ أَن طَهِّرَا بَيْتِيَ لِلطَّائِفِينَ وَالْعَاكِفِينَ وَالرُّكَّعِ السُّجُودِ}

(Ẹ rántí) nígbà tí A ṣe Ilé (Kaaba) ní àyè tí àwọn ènìyàn yóò máa wá àti àyè ìfàyàbalẹ̀. Kí ẹ sì mú ibùdúró ’Ibrọ̄hīm ní ibùkírun. A sì pa (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm àti (Ànábì) ’Ismọ̄‘īl láṣẹ pé “Ẹ ṣe Ilé Mi ní mímọ́ fún àwọn olùyípo rẹ̀, àwọn olùkóraró sínú rẹ̀ àti àwọn olùdáwọ́tẹ-orúnkún, àwọn olùforíkanlẹ̀ (lórí ìrun). Al-Baqara 125 Ọlọhun tun ṣe e ni ọranyan fun Musa nibi ipepe àkọ́kọ́ ti Ọlọhun pe Musa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ إِنِّي أَنَا رَبُّكَ فَاخْلَعْ نَعْلَيْكَ ۖ إِنَّكَ بِالْوَادِ الْمُقَدَّسِ طُوًى (12) وَأَنَا اخْتَرْتُكَ فَاسْتَمِعْ لِمَا يُوحَىٰ (13) إِنَّنِي أَنَا اللَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا أَنَا فَاعْبُدْنِي وَأَقِمِ الصَّلَاةَ لِذِكْرِي (14) }

Dájúdájú Èmi ni Olúwa rẹ. Nítorí náà, bọ́ bàtà rẹ méjèèjì sílẹ̀. Dájúdájú ìwọ wà ní àfonífojì mímọ́, Tuwā.

Àti pé Èmi ṣà ọ́ lẹ́ṣà. Nítorí náà, fi etí sí ohun tí A máa fi ránṣẹ́ sí ọ nínú ìmísí.

Dájúdájú Èmi ni Allāhu. Kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi. Nítorí náà, jọ́sìn fún Mi. Kí o sì kírun fún ìrántí Mi. Suratu Ta-ha: 12-14. Anọbi Isa- ki ikẹ Ọlọhun máa ba a- sọ pe Ọlọhun pa oun láṣẹ irun ati zakat, o wa sọ gẹ́gẹ́ bí Ọlọhun ṣe fun wa ni iro pe:

{ وَجَعَلَنِي مُبَارَكًا أَيْنَ مَا كُنتُ وَأَوْصَانِي بِالصَّلَاةِ وَالزَّكَاةِ مَا دُمْتُ حَيًّا }

Ó ṣe mí ní ẹni ìbùkún ní ibikíbi tí mo bá wà. Ó pa mí láṣẹ ìrun kíkí àti Zakāh yíyọ lódiwọ̀n ìgbà tí mo bá wà nípò alààyè (lórí ilẹ̀ ayé). Maryam 31 Irun ninu Islam naa ni diduro ati titẹ kọkọrọ, ati iforikanlẹ ati iranti Ọlọhun ati yiyin-In ati adua, ọmọniyan yoo maa ki i ni ẹẹmarun ni ojoojumọ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ حَافِظُوا عَلَى الصَّلَوَاتِ وَالصَّلَاةِ الْوُسْطَىٰ وَقُومُوا لِلَّهِ قَانِتِينَ }

Ẹ ṣọ́ àwọn ìrun (wákàtí márààrún) àti (ní pàápàá jùlọ) ìrun ààrin. Kí ẹ sì dúró (kírun gẹ́gẹ́ bí) olùtẹríba fún Allāhu, láì níí sọ̀rọ̀ (mìíràn lórí ìrun). Al-Baqara 238 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe: Gbé ìrun kíkí dúró ní (ìgbà tí) òòrùn bá yẹ̀tàrí títí di ìgbà tí alẹ́ yóò fi lẹ́. Àti pé ìrun Subh, dájúdájú ìrun Subh jẹ́ ohun tí (àwọn mọlāika alẹ́ àti ọ̀sán) yóò jẹ́rìí sí. AL-ISROO 78 O tun sọ– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– pe:

(فَأَمَّا الرُّكُوعُ فَعَظِّمُوا فِيهِ الرَّبَّ عَزَّ وَجَلَّ وَأَمَّا السُّجُودُ فَاجْتَهِدُوا فِي الدُّعَاءِ فَقَمِنٌ أَنْ يُسْتَجَابَ لَكُمْ)

"Ti ẹ ba ti wa ni rukuu ki ẹ gbe Ọluwa tobi nibẹ, ti ẹ ba wa ni iforikanlẹ, ki ẹ gbìyànjú láti ṣe adua nibẹ, nkan ti o tọ́ ni ki wọn gba adua yin Sohiihu ti Muslim

2. Ẹlẹẹkeji: Zakat, Ọlọhun ṣe e ni ọranyan lórí àwọn Musulumi gẹ́gẹ́ bí O ṣe ṣe e ni ọranyan fún àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ ti wọn ṣíwájú (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn), oun naa ni odiwọn kékeré nínú dúkìá ni ibamu si awọn májẹ̀mú ati awọn ipebubu ti Ọlọhun pebubu rẹ, ti o jẹ dandan ninu dúkìá àwọn ọlọrọ, ti wọn maa fun àwọn aláìní àti àwọn tí wọn yàtọ̀ si wọn ni ẹẹkan ni ọdun, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ خُذْ مِنْ أَمْوَالِهِمْ صَدَقَةً تُطَهِّرُهُمْ وَتُزَكِّيهِم بِهَا وَصَلِّ عَلَيْهِمْ ۖ إِنَّ صَلَاتَكَ سَكَنٌ لَّهُمْ ۗ وَاللَّهُ سَمِيعٌ عَلِيمٌ }

Gba ọrẹ (Zakāh) nínú dúkìá wọn, kí o fi sọ wọ́n di ẹni mímọ́, kí o sì fi ṣe àfọ̀mọ́ fún wọn. Ṣe àdúà fún wọn. Dájúdájú àdúà rẹ ni ìfàyàbalẹ̀ fún wọn. Allāhu sì ni Olùgbọ́, Onímọ̀. At-Taobah 103 Nígbà tí Anọbi – ki

ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a – ran Muaz- ki Ọlọhun yọnu si i- lọ si Yemen, o sọ fun un pe:

«إِنَّكَ تَأْتِي قَوْمًا أَهْلَ كِتَابٍ فَادْعُهُمِ الَى شَهَادَةِ أَنْ لَا إِلَهَ إِلَّا اللهُ وَأَنِّي رَسُولُ اللهِ فَإِنْ هُمْ أَطَاعُوكَ لِذَلِكَ فَأَعْلِمْهُمْ أَنَّ اللهَ عَزَّ وَجَلَّ افْتَرَضَ عَلَيْهِمْ خَمْسَ صَلَوَاتٍ فِي كُلِّ يَوْمٍ وَلَيْلَةٍ فَإِنْ أَطَاعُوا لِذَلِكَ فَأَعْلِمْهُمْ أَنَّ اللهَ عَزَّ وَجَلَّ افْتَرَضَ عَلَيْهِمْ صَدَقَةً فِي أَمْوَالِهِمْ تُؤْخَذُ مِنْ أَغْنِيَائِهِمْ وَتُرَدُّ فِي فُقَرَائِهِمْ فَإِنْ هُمْ أَطَاعُوكَ لِذَلِكَ فَإِيَّاكَ وَكَرَائِمَ أَمْوَالِهِمْ وَاتَّقِ دَعْوَةَ الْمَظْلُومِ فَإِنَّهَا لَيْسَ بَيْنَهَا وَبَيْنَ اللهِ عَزَّ وَجَلَّ حِجَابٌ»

"Dájúdájú ìwọ yóò wa ba àwọn ìjọ kan ti a fun ni tira, pe wọn lọ sibi ijẹri pe ko si ẹni kankan ti o lẹtọ si ijọsin ni ododo ayafi Allaah, ati pe emi o, ojiṣẹ Ọlọhun ni mi, ti wọn ba ti wa tẹle ọ fun ìyẹn, jẹ ki wọn mọ pe Ọlọhun ti O biyi ti O gbọnngbọn ṣe irun wákàtí maarun ni ọranyan le wọn lori ni ojoojumọ, ti wọn ba ti wa tẹle ọ fun ìyẹn, jẹ ki wọn mọ pe Ọlọhun ṣe zakat yíyọ ninu dúkìá wọn ni ọranyan le wọ́n lori, wọ́n maa gba a lọ́wọ́ àwọn olowo wọn, wọn maa fun àwọn talika wọn, ti wọn ba ti wa tẹle ọ fun ìyẹn, sọra fun eyi ti o ba níye lórí ninu awọn dúkìá wọn, wa ṣọra fun ipepe ẹni tí a ṣe abosi fun, tori ko si gaga kankan laarin rẹ ati Ọlọhun " Tirmiziy ni o gba a wa (625)

3. Ẹlẹẹkẹta: AAWẸ, Ọlọhun ṣe e ni ọranyan fun àwọn Musulumi gẹ́gẹ́ bí ó ṣe ṣe e ni ọranyan fun àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ ti wọn ṣíwájú, kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا كُتِبَ عَلَيْكُمُ الصِّيَامُ كَمَا كُتِبَ عَلَى الَّذِينَ مِن قَبْلِكُمْ لَعَلَّكُمْ تَتَّقُونَ}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, A ṣe ààwẹ̀ náà ní ọ̀ran-anyàn fun yín, gẹ́gẹ́ bí A ti ṣe é ní ọ̀ran-anyàn fún àwọn t’ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè bẹ̀rù (Allāhu). Al-Baqara

183 Oun naa ni kiko ara ro kuro nibi awọn nkan to n ba aawẹ jẹ ni ọsan oṣu Ramadan. Aawẹ si nìyí, o maa n re erongba ati sùúrù sinu ẹ̀mí ni O sọ– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– pe:

«يقُولُ اللَّهُ عَزَّ وَجَلَّ: الصَّوْمُ لِي وَأَنَا أَجْزِي بِهِ يَدَعُ شَهْوَتَهُ وَأَكْلَهُ وَشُرْبَهُ مِنْ أَجْلِي وَالصَّوْمُ جُنَّةٌ وَلِلصَّائِمِ فَرْحَتَانِ: فَرْحَةٌ حِينَ يُفْطِرُ وَفَرْحَةٌ حِينَ يَلْقَى رَبَّهُ»

"Olohun ti O biyi ti O gbọnngbọn n sọ wipe: Èmi ni mo ni aawẹ, Èmi naa si ni maa sẹsan rẹ, yoo fi adùn rẹ silẹ, ati jíjẹ rẹ, àti mimu rẹ, nítorí Mi, aawẹ si niyii, gaga ni o jẹ, ìdùnnú meji si ni o n bẹ fun alaawẹ: ikini nígbà tí ó bá fẹ̀ṣinu, ikeji ni nígbà tí ó bá maa pade Olúwa rẹ" Sohiihu ti Al-Bukhaar 7492

4. Ẹlẹẹkẹrin: AL-HAJJ, Ọlọhun ṣe e ni ọranyan fun àwọn Musulumi gẹ́gẹ́ bí Ó ṣe ṣe e ni ọranyan fun àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ ti wọn ṣíwájú – kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn - Ọlọhun wa pa Anọbi Ibrahim láṣẹ pe ki o pepe fun hajj, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَأَذِّن فِي النَّاسِ بِالْحَجِّ يَأْتُوكَ رِجَالًا وَعَلَىٰ كُلِّ ضَامِرٍ يَأْتِينَ مِن كُلِّ فَجٍّ عَمِيقٍ }

Kí o sì pe ìpè fún àwọn ènìyàn fún iṣẹ́ Hajj. Wọn yóò wá bá ọ pẹ̀lú ìrìn ẹsẹ̀. Wọn yó sì máa gun àwọn ràkúnmí wá láti àwọn ọ̀nà jíjìn Al-Hajj 27 Ọlọhun wa pa a láṣẹ pe ki o fọ Kaaba mọ fun àwọn alalaaji, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَإِذْ بَوَّأْنَا لِإِبْرَاهِيمَ مَكَانَ الْبَيْتِ أَن لَّا تُشْرِكْ بِي شَيْئًا وَطَهِّرْ بَيْتِيَ لِلطَّائِفِينَ وَالْقَائِمِينَ وَالرُّكَّعِ السُّجُودِ }

(Ẹ ránti) nígbà tí A ṣàfi hàn àyè ilé náà fún (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm (A sì pa á láṣẹ) pé o ò gbọdọ̀ sọ kiní kan di akẹgbẹ́ fún Mi. Àti pé kí o ṣe ilé Mi ní mímọ́ fún àwọn

olùyípo rẹ̀, olùkírun, olùdáwọ́tẹ-orúnkún àti olùforíkanlẹ̀. Al-Hajj 26

HAJJ: Oun naa ni lílọ si ile Olúwa ni Mẹka Alapọnle fun àwọn iṣẹ kan ti a mọ ni ẹẹkan ni ìgbésí ayé fún ẹni tí ó bá ni ikapa. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَلِلَّهِ عَلَى النَّاسِ حِجُّ الْبَيْتِ مَنِ اسْتَطَاعَ إِلَيْهِ سَبِيلًا ۚ وَمَن كَفَرَ فَإِنَّ اللَّهَ غَنِيٌّ عَنِ الْعَالَمِينَ}

Allāhu ṣe àbẹ̀wò sí Ilé náà ní dandan fún àwọn ènìyàn, t’ó lágbára ọ̀nà tí ó máa gbà débẹ̀. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì ṣàì gbàgbọ́,dájúdájú Allāhu ni Ọlọ́rọ̀ tí kò bùkátà sí gbogbo ẹ̀dá. Aal Im’raan/97 Ni hajj ni àwọn alalaaji Musulumi ti maa n kójọ ni ààyè kan ṣoṣo lẹniti wọn nṣe àfọ̀mọ́ ìjọsìn fun Adẹda. Gbogbo àwọn alalaaji maa n ṣiṣẹ́ hajj wọn ni ọna ti o jọra ti ko si ìyàtọ̀ agbegbe ati ọlaju ati isẹmi níbẹ̀.

## 24- Lara àwọn nnkan ti o maa n jẹ ki ìjọsìn o da yàtọ̀ ju nínú Islam ni àwọn ọna ti a n gba ṣe e, àti àwọn àsìkò rẹ, àti àwọn májẹ̀mú rẹ, Ọlọhun ṣe e ni òfin, O si mu u de ọdọ ojiṣẹ Rẹ, abara kankan ko si le e kun tabi din in ku titi di òní, gbogbo àwọn ìjọsìn ńlá ńlá yii ni gbogbo àwọn Anọbi naa pepe si, ki ọlà Ọlọhun lọ máa bá wọn.

Lara àwọn nnkan ti o maa n jẹ ki ìjọsìn o da yàtọ̀ ju nínú Islam ni àwọn ọna ti a n gba ṣe e, àti àwọn àsìkò

rẹ, àti àwọn májẹ̀mú rẹ, Ọlọhun ṣe e ni òfin, O si mu u de ọdọ ojiṣẹ Rẹ, abara kankan ko si le e kun tabi din in ku titi di òní, Olohun ti ola Re ga so pe:

{ ٱلۡيَوۡمَ أَكۡمَلۡتُ لَكُمۡ دِينَكُمۡ وَأَتۡمَمۡتُ عَلَيۡكُمۡ نِعۡمَتِي وَرَضِيتُ لَكُمُ ٱلۡإِسۡلَٰمَ دِينٗاۚ}

Mo parí ẹ̀sìn yín fun yín lónìí. Mo sì ṣe àṣepé ìdẹ̀ra Mi fun yín. Mo sì yọ́nú sí ’Islām ní ẹ̀sìn fun yín (Al'Maa'idah 3) Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{فَٱسۡتَمۡسِكۡ بِٱلَّذِيٓ أُوحِيَ إِلَيۡكَۖ إِنَّكَ عَلَىٰ صِرَٰطٖ مُّسۡتَقِيمٖ}

Nítorí náà, di ohun tí A fi ránṣẹ́ sí ọ mú ṣinṣin. Dájúdájú ìwọ wà lójú ọ̀nà tààrà (’Islām). Az-Zukhruf 43 Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ nípa irun pé :

{فَإِذَا قَضَيْتُمُ الصَّلَاةَ فَاذْكُرُوا اللَّهَ قِيَامًا وَقُعُودًا وَعَلَىٰ جُنُوبِكُمْ ۚ فَإِذَا اطْمَأْنَنتُمْ فَأَقِيمُوا الصَّلَاةَ ۚ إِنَّ الصَّلَاةَ كَانَتْ عَلَى الْمُؤْمِنِينَ كِتَابًا مَّوْقُوتًا}

Nígbà tí ẹ bá parí ìrun, kí ẹ ṣe (gbólóhùn) ìrántí Allāhu ní ìdúró, ìjókòó àti ìdùbúlẹ̀ yín. Nígbà tí ẹ bá sì fọkàn balẹ̀ (ìyẹn nígbà tí ẹ bá wọnú ìlú), kí ẹ kírun (ní pípé). Dájúdájú ìrun kíkí jẹ́ ọ̀ran-anyàn tí A fi àkókò sí fún àwọn onígbàgbọ́ òdodo. An-Nisa 103 Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ nípa àwọn ibi tí a maa yọ zakat si wipe:

{ إِنَّمَا ٱلصَّدَقَٰتُ لِلۡفُقَرَآءِ وَٱلۡمَسَٰكِينِ وَٱلۡعَٰمِلِينَ عَلَيۡهَا وَٱلۡمُؤَلَّفَةِ قُلُوبُهُمۡ وَفِي ٱلرِّقَابِ وَٱلۡغَٰرِمِينَ وَفِي سَبِيلِ ٱللَّهِ وَٱبۡنِ ٱلسَّبِيلِۖ فَرِيضَةٗ مِّنَ ٱللَّهِۗ وَٱللَّهُ عَلِيمٌ حَكِيمٞ}

Àwọn tí ọrẹ (Zakāh) wà fún ni àwọn aláìní, àwọn mẹ̀kúnnù, àwọn òṣìṣẹ́ Zakāh, àwọn tí ọkàn wọn fẹ́ gba ’Islām, àwọn ẹrú (fún gbígba òmìnira), àwọn onígbèsè, àwọn t’ó wà lójú ogun (ẹ̀sìn) Allāhu àti onírìn-àjò (tí agara dá). Ọ̀ran-anyàn ni láti ọ̀dọ̀ Allāhu. Allāhu sì ni Onímọ̀, Ọlọ́gbọ́n. At-Taobah 60 Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ nípa aawẹ pe:

{ شَهۡرُ رَمَضَانَ ٱلَّذِيٓ أُنزِلَ فِيهِ ٱلۡقُرۡءَانُ هُدٗى لِّلنَّاسِ وَبَيِّنَٰتٖ مِّنَ ٱلۡهُدَىٰ وَٱلۡفُرۡقَانِۚ فَمَن شَهِدَ مِنكُمُ ٱلشَّهۡرَ فَلۡيَصُمۡهُۖ وَمَن كَانَ مَرِيضًا أَوۡ عَلَىٰ سَفَرٖ فَعِدَّةٞ مِّنۡ أَيَّامٍ أُخَرَۗ يُرِيدُ ٱللَّهُ بِكُمُ ٱلۡيُسۡرَ وَلَا يُرِيدُ بِكُمُ ٱلۡعُسۡرَ وَلِتُكۡمِلُواْ ٱلۡعِدَّةَ وَلِتُكَبِّرُواْ ٱللَّهَ عَلَىٰ مَا هَدَىٰكُمۡ وَلَعَلَّكُمۡ تَشۡكُرُونَ}

Oṣù Rọmọdọ̄n èyí tí A sọ al-Ḱur'ān kalẹ̀ nínú rẹ̀ 1 (tí ó jẹ́) ìmọ̀nà, àwọn àlàyé pọ́nńbélé nípa ìmọ̀nà àti ọ̀rọ̀-ìpínyà 2 fún àwọn ènìyàn; nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí ó bá wà nínú ìlú rẹ̀ nínú yín nínú oṣù náà, 3 kí ó gba ààwẹ̀ oṣù náà. Ẹnikẹ́ni tí ó bá jẹ́ aláìsàn tàbí tí ó bá wà lórí ìrìn-àjò, (ó máa san) òǹkà (gbèsè ààwẹ̀ rẹ̀) ní àwọn ọjọ́ mìíràn. Allāhu fẹ́ ìrọ̀rùn fun yín, kò sì fẹ́ ìnira fun yín. Ẹ pé òǹkà (ọjọ́ ààwẹ̀), kí ẹ sì gbé títóbi fún Allāhu nítorí pé Ó fi ọ̀nà mọ̀ yín àti nítorí kí ẹ lè dúpẹ́ fún Un. Al-Baqara 185 Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ nípa hajj pé :

{ ٱلۡحَجُّ أَشۡهُرٞ مَّعۡلُومَٰتٞۚ فَمَن فَرَضَ فِيهِنَّ ٱلۡحَجَّ فَلَا رَفَثَ وَلَا فُسُوقَ وَلَا جِدَالَ فِي ٱلۡحَجِّۗ وَمَا تَفۡعَلُواْ مِنۡ خَيۡرٖ يَعۡلَمۡهُ ٱللَّهُۗ وَتَزَوَّدُواْ فَإِنَّ خَيۡرَ ٱلزَّادِ ٱلتَّقۡوَىٰۖ وَٱتَّقُونِ يَٰٓأُوْلِي ٱلۡأَلۡبَٰبِ}

Hajj ṣíṣe (wà) nínú àwọn oṣù tí A ti mọ̀. Nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe é ní ọ̀ran-anyàn lórí ara rẹ̀ láti ṣe Hajj nínú àwọn oṣù náà, kò gbọdọ̀ sí oorun ìfẹ́, ẹ̀ṣẹ̀ dídá àti àríyànjiyàn nínú iṣẹ́ Hajj. Ohunkóhun tí ẹ bá ṣe ní rere, Allāhu mọ̀ ọ́n. Ẹ mú èsè ìrìn-àjò lọ́wọ́. Dájúdájú èsè ìrìn-àjò t'ó lóore jùlọ ni ìṣọ́ra (níbi èsè ẹlòmíìràn àti agbe ṣíṣe l'ásìkò iṣẹ́ Hajj). Ẹ bẹ̀rù Mi, ẹ̀yin onílàákàyè. Al-Baqara 197 Gbogbo àwọn ìjọsìn ńlá yii ni gbogbo àwọn Anọbi pátá pepe si, ki ọlà Ọlọhun maa ba wọn

## 25. Ojiṣẹ ẹsin Isilaamu naa ni Muhammad ọmọ Abdullaah ti o wa

nínú àwọn arọmọdọmọ Ismail ọmọ Ibrahim (ki ọlà Ọlọhun maa ba wọn). Wọn bi i si ìlú Mẹka ni ọdún 571 ti hijra, wọn gbe e dide ni ojiṣẹ nibẹ, o ṣi ṣe hijra lati ibẹ lọ sí ìlú Mẹdina. Ko ba àwọn ìjọ rẹ kópa nibi alaamọri oosa, ṣùgbọ́n ó máa ń ba wọn kópa nibi àwọn iṣẹ́ ti o gbọnngbọn. Ìwà rẹ dara ṣíwájú ki o to di ojiṣẹ ti àwọn ìjọ rẹ si maa n pe e ni olufọkantan. Ọlọhun gbe e dìde ni ojiṣẹ nigba ti o pe ọmọ ogoji ọdún, O si kun un lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn nkan ìyanu ńlá, eyi ti o tobi ju nínú rẹ naa ni Alukurani Alapọnle, oun si ni o tobi ju ninu awọn àmì àwọn Anọbi, oun naa ṣi ni àmì ti o n ṣẹku ninu awọn àmì àwọn Anọbi títí di òní. Nígbà tí Ọlọhun pe ẹsin fun un, ti ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- náà si jẹẹ bi o ṣe tọ ati bí ó ṣe yẹ, o kú ni ọmọọdún mẹta lé ni ọgọta, wọ́n sin in sí ìlú Mẹdina, oun si ni igbẹyin àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ, Ọlọhun gbe e dìde pẹ̀lú imọna àti

**ẹsin òdodo, lati mu àwọn ènìyàn kúrò nínú òkùnkùn ibọrisa, aigbagbọ, ati aimọkan, lọ sibi imọlẹ imọỌlọhun lọkan ati ìgbàgbọ́, Ọlọhun si jẹri si i pe Oun ni Oun gbe e dìde láti maa pepe sibẹ pẹ̀lú iyọnda Rẹ.**

Ojiṣẹ ẹsin Isilaamu naa ni Muhammad ọmọAbdullaah ti o wa nínú àwọn arọmọdọmọ Ismail ọmọ Ibrahim (ki ọlà Ọlọhun maa ba wọn). Wọn bi i si ìlú Mẹka ni ọdún 571 ti hijra, wọn gbe e dide ni ojiṣẹ nibẹ, o ṣi ṣe hijra lati ibẹ lọ sí ìlú Mẹdina. Àwọn eeyan rẹ máa ń pe e ni olufọkantan, Ko ba àwọn ìjọ rẹ kópa nibi alaamọri oosa, ṣùgbọ́n ó máa ń ba wọn kópa nibi àwọn iṣẹ́ ti o gbọnngbọn, o si ni ìwà ti o dara gan ṣíwájú ki o to di ojiṣẹ, Olúwa rẹ royin rẹ pẹ̀lú ìwà ti o dára gan, O sọ nípa rẹ̀ pe:

{وَإِنَّكَ لَعَلَىٰ خُلُقٍ عَظِيمٍ}

Dájúdájú ìwọ sì wà lórí ìwà àpọ́nlé. Al-Qalam 4

Ọlọhun gbe e dide ni ojiṣẹ nígbà tí ó pé ọmọ ogójì ọdún, O si kun un lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn àmì ńlá, èyí tí ó tóbi jù nínú rẹ̀ náà ni Kuraani Alapọn-ọnle Ojiṣẹ Rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«مَا مِنَ الأَنْبِيَاءِ نَبِيٌّ إِلَّا أُعْطِيَ مَا مِثْلُهُ آمَنَ عَلَيْهِ البَشَرُ وَإِنَّمَا كَانَ الَّذِي أُوتِيتُ وَحْيًا أَوْحَاهُ اللَّهُ إِلَيَّ فَأَرْجُو أَنْ أَكُونَ أَكْثَرَهُمْ تَابِعًا يَوْمَ القِيَامَةِ»

"Ko si Anọbi kan nínú àwọn Anọbi Ọlọhun afi kí Ọlọhun fun un ni àmì tí àwọn èèyàn a torí irú rẹ gba a gbọ, àmọ́ nnkan ti wọn fún èmi ni imisi tí Ọlọhun mi i

si mi, mo wa n ni ìrètí pé ki n jẹẹni tí olutẹle rẹ yóò pọ ju nínú àwọn Anọbi ni ọjọ igbende alukiyaamọ" Sohiihul-Bukhaariy Alukurani ni imisi Ọlọhun si ojiṣẹ Rẹ- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- Ọlọhun sọ nípa rẹ pe:

{ ذَٰلِكَ الْكِتَابُ لَا رَيْبَ ۛ فِيهِ ۛ هُدًى لِّلْمُتَّقِينَ }

Èyí ni Tírà náà, tí kò sí iyèméjì nínú rẹ̀. Ìmọ̀nà ni fún àwọn olùbẹ̀rù (Allāhu); Al-Baqara 2 Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ nípa rẹ̀ pé:

{أَفَلَا يَتَدَبَّرُونَ الْقُرْآنَ ۚ وَلَوْ كَانَ مِنْ عِندِ غَيْرِ اللَّهِ لَوَجَدُوا فِيهِ اخْتِلَافًا كَثِيرًا}

Ṣé wọn kò ronú nípa al-Ḳur’ān ni? Tí ó bá jẹ́ pé ó wá láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíìràn yàtọ̀ sí Allāhu, wọn ìbá rí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìtakora nínú rẹ̀. An-Nisaa 82 Ọlọhun pe àwọn alujannu ati awọn ènìyàn nija lati mu irú rẹ wa, Ọlọhun sọ pe:

{قُل لَّئِنِ اجْتَمَعَتِ الْإِنسُ وَالْجِنُّ عَلَىٰ أَن يَأْتُوا بِمِثْلِ هَٰذَا الْقُرْآنِ لَا يَأْتُونَ بِمِثْلِهِ وَلَوْ كَانَ بَعْضُهُمْ لِبَعْضٍ ظَهِيرًا}

Sọ pé: “Dájúdájú tí àwọn ènìyàn àti àlùjànnú bá para pọ̀ láti mú irú al-Ḳur’ān yìí wá, wọn kò lè mú irú rẹ̀ wá, apá kan wọn ìbáà jẹ́ olùrànlọ́wọ́ fún apá kan." AL-ISROO 88 Ọlọhun tún pe wọn nija lati mu suura mẹwa ninu irú rẹ wa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ أَمْ يَقُولُونَ افْتَرَاهُ ۖ قُلْ فَأْتُوا بِعَشْرِ سُوَرٍ مِّثْلِهِ مُفْتَرَيَاتٍ وَادْعُوا مَنِ اسْتَطَعْتُم مِّن دُونِ اللَّهِ إِن كُنتُمْ صَادِقِينَ }

Tàbí wọ́n ń wí pé: “Ó hun ún ni.” Sọ pé: “Ẹ mú sūrah mẹ́wàá àdáhun bí irú rẹ̀ wá, kí ẹ sì ké sí ẹni tí ẹ bá lè ké sí lẹ́yìn Allāhu tí ẹ bá jẹ́ olódodo.” Huud 13 Ọlọhun tun pe wọn nija lati mu suura ẹyọkan bii irú rẹ

wa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Tí ẹ bá wà nínú iyèméjì nípa ohun tí A sọ̀kalẹ̀ fún ẹrúsìn Wa, nítorí náà, ẹ mú sūrah kan wá bí irú rẹ̀, kí ẹ sì pe àwọn ẹlẹ́rìí yín, yàtọ̀ sí Allāhu, tí ẹ bá jẹ́ olódodo. Al-Baqara 23

Alukurani nìkan ni àmì ti o ṣẹku nínú àwọn àmì àwọn Anọbi títí di òní, nígbà tí Ọlọhun pé ẹsin fun ojiṣẹ Rẹ ti ojiṣẹ naa si jẹ bi o ṣe tọ àti bí ó ṣe yẹ, lẹ́yìn náà ni o ku ni ọmọọdún mẹ́ta lé ni ọgọta, wọ́n sì sin in si ìlú Mẹdina, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a.

Anọbi Muhammad- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni igbẹyin àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

Anọbi Muhammad- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni igbẹyin àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ مَّا كَانَ مُحَمَّدٌ أَبَا أَحَدٍ مِّن رِّجَالِكُمْ وَلَٰكِن رَّسُولَ اللَّهِ وَخَاتَمَ النَّبِيِّينَ ۗ وَكَانَ اللَّهُ بِكُلِّ شَيْءٍ عَلِيمًا }

(Ànábì) Muhammad kì í ṣe bàbá ẹnì kan kan nínú àwọn ọkùnrin yín, ṣùgbọ́n (ó jẹ́) Òjíṣẹ́ Allāhu àti òpin àwọn Ànábì. Allāhu sì ń jẹ́ Onímọ̀ nípa gbogbo ǹǹkan. Suratul Ahzab: 40 Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọ́nú si i- wípé ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«إِنَّ مَثَلِي وَمَثَلَ الأَنْبِيَاءِ مِنْ قَبْلِي كَمَثَلِ رَجُلٍ بَنَى بَيْتًا فَأَحْسَنَهُ وَأَجْمَلَهُ إِلَّا مَوْضِعَ لَبِنَةٍ مِنْ زَاوِيَةٍ فَجَعَلَ النَّاسُ يَطُوفُونَ بِهِ وَيَعْجَبُونَ لَهُ وَيَقُولُونَ هَلَّا وُضِعَتْ هَذِهِ اللَّبِنَةُ؟ قَالَ: فَأَنَا اللَّبِنَةُ وَأَنَا خَاتِمُ النَّبِيِّينَ»

"Dájúdájú àpèjúwe mi ati àpèjúwe àwọn Anọbi ti wọn ṣíwájú mi, o da gẹgẹ bi àpèjúwe arákùnrin kan ti o kọ ilé kan dáadáa, ti o wa ku síbi ààyè bíríkì kan ni origun

kan lára ilé náà, ti àwọn èèyàn wa bẹrẹ si nii rọkirika ilé náà ti wọn si n se eemọ latara rẹ, ti wọn wa n sọ pé ṣe wọn ko nii gbé bíríkì yii síbẹ̀ ni? O sọ pe: Èmi ni bíríkì náà, èmi ni òpin àwọn Anọbi" Sohiihul-Bukhaariy Nínú Bíbélì, Anọbi Isa- ki ọlà Ọlọhun maa ba a- sọ lẹniti n fun ni ni iro ìdùnnú nípa Anọbi Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a) Òkúta naa ti àwọn ọmọle kọ silẹ ni o wa di orí igun ilé náà, ṣé ẹyin ko ka nínú àwọn Tira naa pe: Anọbi Isa sọ fun wọn pe láti ọ̀dọ̀ Olúwa ni èyí tí wá, eemọ si ni ó jẹ́ ni ojú wa. Ninu ìwé Taoreeta to n bẹ ni oni, o wa nínú ẹ pe Ọlọhun sọ fún Anọbi Musa pe: Maa gbé Anọbi kan bíi ìwọ dìde ni aarin àwọn ọmọ ìyá wọn, Maa fi ọrọ Mi si i lẹnu, yóò máa ba wọn sọ̀rọ̀ pẹ̀lú gbogbo nkan ti mo ba pa a láṣẹ ki o sọ

Ọlọhun gbe Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- dide pẹ̀lú imọna ati ẹsin òdodo, Ọlọhun si jẹri si i pe orí òdodo ni o wa, ati pe Oun gbe e dìde ni olupepe si òdodo pẹ̀lú iyọnda Rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{لَّٰكِنِ اللَّهُ يَشْهَدُ بِمَا أَنزَلَ إِلَيْكَ ۖ أَنزَلَهُ بِعِلْمِهِ ۖ وَالْمَلَائِكَةُ يَشْهَدُونَ ۚ وَكَفَىٰ بِاللَّهِ شَهِيدًا}

Ṣùgbọ́n Allāhu ń jẹ́rìí sí ohun tí Ó sọ̀kalẹ̀ fún ọ. Ó sọ̀ ọ́ kalẹ̀ pẹ̀lú ìmọ̀ Rẹ̀. Àwọn mọlāika náà ń jẹ́rìí (sí i). Allāhu sì tó ní Ẹlẹ́rìí. An-Nisaa 166 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{هُوَ الَّذِي أَرْسَلَ رَسُولَهُ بِالْهُدَىٰ وَدِينِ الْحَقِّ لِيُظْهِرَهُ عَلَى الدِّينِ كُلِّهِ ۚ وَكَفَىٰ بِاللَّهِ شَهِيدًا}

(Allāhu) Òun ni Ẹni tí Ó fi ìmọ̀nà àti ẹ̀sìn òdodo (’Islām) rán Òjíṣẹ́ Rẹ̀ nítorí kí Ó lè fi borí ẹ̀sìn (mìíràn), gbogbo rẹ̀ pátápátá. Allāhu sì tó ní Ẹlẹ́rìí. Al-Fat'h 28 Ọlọhun gbe e dide pẹ̀lú imọna láti mu àwọn ènìyàn kúrò nínú àwọn òkùnkùn ibọrisa àti aigbagbọ ati aimọkan bọ sínú imọlẹ imọỌlọhun lọkan ati ìgbàgbọ́, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{يَهْدِي بِهِ اللَّهُ مَنِ اتَّبَعَ رِضْوَانَهُ سُبُلَ السَّلَامِ وَيُخْرِجُهُم مِّنَ الظُّلُمَاتِ إِلَى النُّورِ بِإِذْنِهِ وَيَهْدِيهِمْ إِلَىٰ صِرَاطٍ مُّسْتَقِيمٍ}

Allāhu ń fi (al-Ƙur’ān) ṣe ìmọ̀nà fún ẹnikẹ́ni tí ó bá tẹ̀lé (àwọn ǹǹkan) tí Allāhu yọ́nú sí, àwọn ọ̀nà àlàáfíà. (Allāhu) yó sì mú wọn jáde láti inú àwọn òkùnkùn wá sínú ìmọ́lẹ̀ pẹ̀lú ìyọ̀nda Rẹ̀. Ó sì máa tọ́ wọn sí ọ̀nà tààrà (’Islām). Al-Maa'ida 16 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{الر ۚ كِتَابٌ أَنزَلْنَاهُ إِلَيْكَ لِتُخْرِجَ النَّاسَ مِنَ الظُّلُمَاتِ إِلَى النُّورِ بِإِذْنِ رَبِّهِمْ إِلَىٰ صِرَاطِ الْعَزِيزِ الْحَمِيدِ }

’Alif lām rọ̄. (Èyí ni) Tírà kan tí A sọ̀kalẹ̀ fún ọ nítorí kí o lè mú àwọn ènìyàn kúrò láti inú àwọn òkùnkùn wá sínú ìmọ́lẹ̀ pẹ̀lú ìyọ̀nda Olúwa wọn. (Wọn yó sì bọ́) sí ọ̀nà Alágbára, Ọlọ́pẹ́ (tí ọpẹ́ tọ́ sí), Ibrahim 1

## 26. Sheria Islam ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mu wa naa ni òpin àwọn iṣẹ-riran ti Ọlọhun ati awọn òfin Rẹ, oun si ni òfin ti o pe ti dídára ẹsin ọmọniyan ati ayé rẹ n bẹ

**nibẹ, o si n sọ: Ẹsin àwọn èèyàn, ati ẹjẹ wọn, ati dúkìá wọn, ati làákàyè wọn, àti àwọn ọmọ wọn, o si ti pa gbogbo òfin ti o ṣíwájú rẹ rẹ, gẹ́gẹ́ bí àwọn òfin tí ó ṣíwájú naa ṣe pa ara wọn rẹ.**

Sheria Islam ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mu wa naa ni òpin àwọn iṣẹ-riran ti Ọlọhun ati awọn òfin Rẹ, Ọlọhun si fi iṣẹ-riran yii pe ẹsin, ti idẹra si pari lórí àwọn ènìyàn pẹ̀lú gbígbé Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- dide ni Ojiṣẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{الْيَوْمَ أَكْمَلْتُ لَكُمْ دِينَكُمْ وَأَتْمَمْتُ عَلَيْكُمْ نِعْمَتِي وَرَضِيتُ لَكُمُ الْإِسْلَامَ دِينًا}

Mo parí ẹ̀sìn yín fun yín lónìí. Mo sì ṣe àṣepé ìdẹ̀ra Mi fun yín. Mo sì yọ́nú sí ’Islām ní ẹ̀sìn fun yín. (Al'Maa'idah 3)

Òfin Islam ni òfin pípé ti dídára ẹ̀sìn ọmọniyan ati ayé wọn n bẹ nínú ẹ; torí pé ó kó gbogbo nkan to n bẹ nínú àwọn òfin tí ó ṣíwájú sínú ti o si pé wọn, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ إِنَّ هَٰذَا الْقُرْآنَ يَهْدِي لِلَّتِي هِيَ أَقْوَمُ وَيُبَشِّرُ الْمُؤْمِنِينَ الَّذِينَ يَعْمَلُونَ الصَّالِحَاتِ أَنَّ لَهُمْ أَجْرًا كَبِيرًا }

Dájúdájú al-Ḳur’ān yìí, ó ń fini mọ̀nà sí ọ̀nà tààrà, ó sì ń fún àwọn onígbàgbọ́ òdodo t’ó ń ṣe àwọn iṣẹ́ rere ní ìró ìdùnnú pé dájúdájú ẹ̀san t’ó tóbi wà fún wọn. AL-ISROO 9 Òfin Islam wa gbe ẹrù wúwo ti wọn di ru

àwọn ìjọ tí wọ́n saaju kúrò fún àwọn ènìyàn, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{الَّذِينَ يَتَّبِعُونَ الرَّسُولَ النَّبِيَّ الْأُمِّيَّ الَّذِي يَجِدُونَهُ مَكْتُوبًا عِندَهُمْ فِي التَّوْرَاةِ وَالْإِنجِيلِ يَأْمُرُهُم بِالْمَعْرُوفِ وَيَنْهَاهُمْ عَنِ الْمُنكَرِ وَيُحِلُّ لَهُمُ الطَّيِّبَاتِ وَيُحَرِّمُ عَلَيْهِمُ الْخَبَائِثَ وَيَضَعُ عَنْهُمْ إِصْرَهُمْ وَالْأَغْلَالَ الَّتِي كَانَتْ عَلَيْهِمْ ۚ فَالَّذِينَ آمَنُوا بِهِ وَعَزَّرُوهُ وَنَصَرُوهُ وَاتَّبَعُوا النُّورَ الَّذِي أُنزِلَ مَعَهُ ۙ أُولَٰئِكَ هُمُ الْمُفْلِحُونَ}

Àwọn t'ó ń tẹ̀lé Òjíṣẹ́ náà, Ànábì aláìmọ̀ọ́nkọmọ̀ọ́nkà, ẹni tí wọ́n yóò bá àkọsílẹ̀ nípa rẹ̀ lọ́dọ̀ wọn nínú at-Taorāh àti al-'Injīl, tí ó ń pa wọ́n láṣẹ ohun rere, tí ó ń kọ ohun burúkú fún wọn, tí ó ń ṣe àwọn ñǹkan dáadáa lẹ́tọ̀ọ́ fún wọn, tí ó sì ń ṣe àwọn ñǹkan àìdáa léèwọ̀ fún wọn, tí ó tún máa gbé ẹrù (àdéhùn t'ó wúwo) àti àjàgà t'ó ń bẹ lọ́rùn wọn kúrò fún wọn; àwọn t'ó gbàgbọ́ nínú rẹ̀, tí wọ́n bu iyì fún un, tí wọ́n ràn án lọ́wọ́, tí wọ́n sì tẹ̀lé ìmọ́lẹ̀ náà (ìyẹn, al-Ḱur'ān) tí A sọ̀kalẹ̀ fún un, àwọn wọ̀nyẹn ni olùjèrè. Al-A'rọọf 157

Òfin Islam ni o pa gbogbo òfin tí ó ṣíwájú rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَأَنزَلْنَا إِلَيْكَ الْكِتَابَ بِالْحَقِّ مُصَدِّقًا لِّمَا بَيْنَ يَدَيْهِ مِنَ الْكِتَابِ وَمُهَيْمِنًا عَلَيْهِ ۖ فَاحْكُم بَيْنَهُم بِمَا أَنزَلَ اللَّهُ ۖ وَلَا تَتَّبِعْ أَهْوَاءَهُمْ عَمَّا جَاءَكَ مِنَ الْحَقِّ ۚ لِكُلٍّ جَعَلْنَا مِنكُمْ شِرْعَةً وَمِنْهَاجًا ۚ وَلَوْ شَاءَ اللَّهُ لَجَعَلَكُمْ أُمَّةً وَاحِدَةً وَلَٰكِن لِّيَبْلُوَكُمْ فِي مَا آتَاكُمْ ۖ فَاسْتَبِقُوا الْخَيْرَاتِ ۚ إِلَى اللَّهِ مَرْجِعُكُمْ جَمِيعًا فَيُنَبِّئُكُم بِمَا كُنتُمْ فِيهِ تَخْتَلِفُونَ}

A sọ Tírà (al-Ḱur'ān) kalẹ̀ fún ọ pẹ̀lú òdodo. Ó ń jẹ́rìí sí èyí t'ó jẹ́ òdodo nínú èyí t'ó ṣíwájú rẹ̀ nínú Tírà. Ó ń wá ààbò fún àwọn òfin inú rẹ̀. Nítorí náà, fi ohun tí Allāhu sọ̀kalẹ̀ dájọ́ láààrin wọn. Má ṣe tẹ̀lé ìfẹ́-inú wọn t'ó yapa sí ohun tí ó dé bá ọ nínú òdodo. Olúkùlùkù nínú yín ni A ti ṣe òfin àti ìlànà fún. Àti pé

tí ó bá jẹ́ pé Allāhu bá fẹ́, ìbá ṣe yín ní ìjọ kan ṣoṣo (sínú ’Islām), ṣùgbọ́n nítorí kí Ó lè dan yín wò nínú ohun tí Ó fun yín ni. Nítorí náà, ẹ gbawájú níbi iṣẹ́ rere. Ọ̀dọ̀ Allāhu ni ibùpadàsí gbogbo yín pátápátá. Ó sì máa fun yín ní ìró nípa ohun tí ẹ̀ ń yapa ẹnu sí. Suratul Maidat: 48 Alukurani ti o ko òfin sínú wa láti jẹrii si èyí tí ó jẹ́ òdodo ninu awọn tira Ọlọhun ti o ṣíwájú, ati lati dajọ le wọn lori, ati lati pa wọn rẹ

## 27. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ko nii tẹ́wọ́ gba ẹsin kankan yàtọ̀ sí Islām ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mu wa, ẹni tí ó bá gba ẹsin míràn yàtọ̀ sí Islām, wọn ko lee gba a lọ́wọ́ẹ lailai

Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ko nii tẹ́wọ́ gba ẹsin kankan yàtọ̀ sí Islām ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mu wa lẹ́yìn tí Ọlọhun ti gbe e dìde ni Ojiṣẹ, ẹni tí ó bá wa ẹsin míràn yàtọ̀ sí Islām, wọn kò nii gba a lọ́wọ́ rẹ lailai Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَمَن يَبْتَغِ غَيْرَ الْإِسْلَامِ دِينًا فَلَن يُقْبَلَ مِنْهُ وَهُوَ فِي الْآخِرَةِ مِنَ الْخَاسِرِينَ}

Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí ’Islām, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò. Aal-Imraan 85 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ إِنَّ الدِّينَ عِندَ اللَّهِ الْإِسْلَامُ ۗ وَمَا اخْتَلَفَ الَّذِينَ أُوتُوا الْكِتَابَ إِلَّا مِن بَعْدِ مَا جَاءَهُمُ الْعِلْمُ بَغْيًا بَيْنَهُمْ ۗ وَمَن يَكْفُرْ بِآيَاتِ اللَّهِ فَإِنَّ اللَّهَ سَرِيعُ الْحِسَابِ}

Dájúdájú ẹ̀sìn t'ó wà lọ́dọ̀ Allāhu ni 'Islām. Àwọn tí A fún ní Tírà (àwọn yẹhudi àti kristiẹni) kò yapa ẹnu (sí ẹ̀sìn náà) àfi lẹ́yìn tí ìmọ̀ dé bá wọn. (Wọ́n ṣe bẹ́ẹ̀) nípasẹ̀ ọ̀tẹ̀ ààrin wọn (sí àwọn Ànábì). Ẹni t'ó bá ṣàì gbàgbọ́ nínú àwọn āyah Allāhu, dájúdájú Allāhu ni Olùyára níbi ìṣírò-iṣẹ́. Aal-Imraan 19 Islam yii ni ẹsin Anọbi Ibrahim tii ṣe ààyò Ọlọhun, ki ọlà Ọlọhun maa ba a, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَمَن يَرْغَبُ عَن مِّلَّةِ إِبْرَاهِيمَ إِلَّا مَن سَفِهَ نَفْسَهُ ۚ وَلَقَدِ اصْطَفَيْنَاهُ فِي الدُّنْيَا ۖ وَإِنَّهُ فِي الْآخِرَةِ لَمِنَ الصَّالِحِينَ}

Ta sì ni ó máa kọ ẹ̀sìn (Ànábì) 'Ibrọ̄hīm sílẹ̀ àfi ẹni tí ó bá gọ ẹ̀mí ara rẹ̀. A kúkú ti ṣà á lẹ́ṣà n'ílé ayé. Dájúdájú ó tún wà nínú àwọn ẹni rere ní ọ̀run. Suratul Baqarat: 130 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَمَنْ أَحْسَنُ دِينًا مِّمَّنْ أَسْلَمَ وَجْهَهُ لِلَّهِ وَهُوَ مُحْسِنٌ وَاتَّبَعَ مِلَّةَ إِبْرَاهِيمَ حَنِيفًا ۗ وَاتَّخَذَ اللَّهُ إِبْرَاهِيمَ خَلِيلًا}

Ta l'ó dára ní ẹ̀sìn ju ẹni tí ó jura rẹ̀ sílẹ̀ fún Allāhu, olùṣe-rere sì tún ni, ó tún tẹ̀lé ẹ̀sìn (Ànábì) 'Ibrọ̄hīm, olùdúró-déédé-nínú-'Islām? Allāhu sì mú (Ànábì) 'Ibrọ̄hīm ní àyànfẹ́. Suratu Nisai: 125 Ọlọhun wa pa Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- láṣẹ ki o sọ pe:

{قُلْ إِنَّنِي هَدَانِي رَبِّي إِلَىٰ صِرَاطٍ مُّسْتَقِيمٍ دِينًا قِيَمًا مِّلَّةَ إِبْرَاهِيمَ حَنِيفًا ۚ وَمَا كَانَ مِنَ الْمُشْرِكِينَ}

Sọ pé: "Dájúdájú Olúwa mi ti fi ọ̀nà tààrà ('Islām) mọ̀ mí, ẹ̀sìn t'ó fẹsẹ̀ rinlẹ̀, ẹ̀sìn (Ànábì) 'Ibrọ̄hīm, olùdúró-déédé-nínú-ẹ̀sìn, kò sì sí nínú àwọn ọ̀ṣẹbọ." Al-An'aam 161

**28. Alukurani Alapọnle ni tira ti Ọlọhun fi ránṣẹ́ si Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- oun si ni ọrọ Olúwa gbogbo àgbáyé, Ọlọhun pe àwọn èèyàn ati alujannu nija lati mu irú rẹ wa, tabi suura kan nínú irú rẹ, ipenija naa ṣi n bẹ titi di òní. Alukurani si n fesi fun àwọn ìbéèrè pàtàkì ti o pọ ti o n ko idamudaabo ba ẹgbẹẹgbẹ̀rún ninu awọn èèyàn. Alukurani yii nkan ti a sọ ni titi di òní pẹ̀lú èdè Lárúbáwá ti o fi sọkalẹ, ti arafi kankan ko si dinku níbẹ̀, wọ́n tẹẹ jáde, wọ́n sì fọn ọn ka, tira nla ni tii ko agara ba ẹni tí ó bá fẹ́ mu irú rẹ wa, nǹkan ti o lẹ́tọ̀ọ́ si kíkà ni tabi kika ongbifọ àwọn ìtumọ̀ rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bẹẹ naa ni ìlànà Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati ẹkọ rẹ ati ìtàn ìgbésí ayé rẹ, gbogbo ẹ ni wọ́n ṣọ tí wọ́n si gbe de ọdọ wa ni ibamu si sisẹntẹle latiọdọ àwọn ti wọn maa n gba ẹgbawa ti wọn ṣee fi ọkan tan. Wọn tẹ oun naa jáde pẹ̀lú èdè**

**Lárúbáwá tii ṣe èdè Anọbi Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a), wọn si túmọ̀ rẹ si ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn èdè. Alukurani ati Sunna ni ipilẹ kan ṣoṣo fun àwọn idajọ Islam ati awọn òfin rẹ. Wọn kii mu Islam latara ìwà àwọn ti wọn n pe apemọra rẹ, bi ko ṣe wipe wọn maa n mu u latara imisi ti Ọlọhun tii ṣe Alukurani ati Sunna.**

Alukurani Alapọnle ni tira ti Ọlọhun fi ránṣẹ́ si Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ti o jẹọmọ Lárúbáwá pẹ̀lú èdè Lárúbáwá, oun naa si ni ọrọ Olúwa gbogbo àgbáyé, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَإِنَّهُ لَتَنزِيلُ رَبِّ الْعَالَمِينَ (192) نَزَلَ بِهِ الرُّوحُ الْأَمِينُ (193) عَلَىٰ قَلْبِكَ لِتَكُونَ مِنَ الْمُنذِرِينَ (194) بِلِسَانٍ عَرَبِيٍّ مُّبِينٍ (195)}

Dájúdájú al-Ƙur’ān, wọ́n sọ̀ ọ́ kalẹ̀ ni láti ọ̀dọ̀ Olúwa gbogbo ẹ̀dá.

Mọlāika Jibrīl, olùfọkàntán l’ó sọ̀ ọ́ kalẹ̀
sínú ọkàn rẹ nítorí kí o lè wà nínú àwọn olùkìlọ̀
pẹ̀lú èdè Lárúbáwá pọ́nńbélé. As-Shuaraa' 192-195

Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَإِنَّكَ لَتُلَقَّى الْقُرْآنَ مِن لَّدُنْ حَكِيمٍ عَلِيمٍ}

Dájúdájú ò ń gba al-Ƙur’ān làti ọ̀dọ̀ Ọlọ́gbọ́n, Onímọ̀. An-Nam'l 6 Alukurani yii wọn sọ ọ kalẹ láti ọ̀dọ̀ Ọlọhun, o si n jẹrii si òdodo àwọn tira Ọlọhun ti o ṣíwájú rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَمَا كَانَ هَٰذَا الْقُرْآنُ أَن يُفْتَرَىٰ مِن دُونِ اللَّهِ وَلَٰكِن تَصْدِيقَ الَّذِي بَيْنَ يَدَيْهِ وَتَفْصِيلَ الْكِتَابِ لَا رَيْبَ فِيهِ مِن رَّبِّ الْعَالَمِينَ}

Al-Ƙur’ān yìí kì í ṣe ǹǹkan tí ó ṣe é dáhun (láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíìràn) lẹ́yìn Allāhu, ṣùgbọ́n ó ń jẹ́rìí sí èyí t’ó jẹ́ òdodo nínú èyí t’ó ṣíwájú rẹ̀, ó ń ṣe àlàyé (àwọn) Tírà náà. Kò sí iyèméjì nínú rẹ̀. (Ó wá) láti ọ̀dọ̀ Olúwa gbogbo ẹ̀dá. Yunus 37 Alukurani yii wọn sọọ kalẹ láti ọ̀dọ̀ Ọlọhun, o si n jẹrii si òdodo àwọn tira Ọlọhun ti o ṣíwájú rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{إِنَّ هَٰذَا الْقُرْآنَ يَقُصُّ عَلَىٰ بَنِي إِسْرَائِيلَ أَكْثَرَ الَّذِي هُمْ فِيهِ يَخْتَلِفُونَ }

Dájúdájú al-Ƙur’ān yìí yóò máa ṣàlàyé ọ̀rọ̀ fún àwọn ọmọ ’Isrọ̄’īl nípa ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ohun tí wọ́n ń yapa ẹnu sí. An-Nam'l 76 Alukurani ko àwọn ẹri sínú, ni èyí tí yóò jẹ ki àwíjàre wa lórí àwọn ènìyàn pátápátá nibi mímọ àwọn òdodo nípa Ọlọhun ti ọla Rẹ ga, àti ẹ̀sìn Rẹ ati ẹsan Rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَلَقَدْ ضَرَبْنَا لِلنَّاسِ فِي هَٰذَا الْقُرْآنِ مِن كُلِّ مَثَلٍ لَّعَلَّهُمْ يَتَذَكَّرُونَ}

A sì ti ṣe gbogbo àkàwé fún àwọn ènìyàn nínú al-Ƙur’ān yìí nítorí kí wọ́n lè lo ìrántí. Az-Zumar 27 Allah tun sọ pe:

{وَنَزَّلْنَا عَلَيْكَ ٱلْكِتَٰبَ تِبْيَٰنًا لِّكُلِّ شَيْءٍ وَهُدًى وَرَحْمَةً وَبُشْرَىٰ لِلْمُسْلِمِينَ}

A sọ Tírà kalẹ̀ fún ọ; (ó jẹ́) àlàyé fún gbogbo ǹǹkan, ìmọ̀nà, ìkẹ́ àti ìró ìdùnnú fún àwọn mùsùlùmí. An-Nah'l 89

Alukurani Alapọnle maa n fèsì fún àwọn ìbéèrè pàtàkì ti o pọ ti o maa n ko idamudaabo ba ẹgbẹẹgbẹ̀rún nínú àwọn ènìyàn. Alukurani Alapọn-ọnle maa n

ṣàlàyé biỌlọhun ṣe da sanmọ àti ilẹ̀, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{أَوَلَمْ يَرَ الَّذِينَ كَفَرُوا أَنَّ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضَ كَانَتَا رَتْقًا فَفَتَقْنَاهُمَا ۖ وَجَعَلْنَا مِنَ الْمَاءِ كُلَّ شَيْءٍ حَيٍّ ۖ أَفَلَا يُؤْمِنُونَ }

Ṣé àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́ kò rí i pé dájúdájú àwọn sánmọ̀ lẹ̀ pọ̀ àti ilẹ̀ náà lẹ̀ pọ̀ tẹ́lẹ̀ ni, A sì yà wọ́n sí ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, A sì ṣe gbogbo ǹǹkan ní abẹ̀mí láti inú omi? Nítorí náà, ṣé wọn kò níí gbàgbọ́ ni? Al-Anbiyaa 30

Báwo wá ni Ọlọhun ṣe da ọmọniyan, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِن كُنتُمْ فِي رَيْبٍ مِّنَ الْبَعْثِ فَإِنَّا خَلَقْنَاكُم مِّن تُرَابٍ ثُمَّ مِن نُّطْفَةٍ ثُمَّ مِنْ عَلَقَةٍ ثُمَّ مِن مُّضْغَةٍ مُّخَلَّقَةٍ وَغَيْرِ مُخَلَّقَةٍ لِّنُبَيِّنَ لَكُمْ ۚ وَنُقِرُّ فِي الْأَرْحَامِ مَا نَشَاءُ إِلَىٰ أَجَلٍ مُّسَمًّى ثُمَّ نُخْرِجُكُمْ طِفْلًا ثُمَّ لِتَبْلُغُوا أَشُدَّكُمْ ۖ وَمِنكُم مَّن يُتَوَفَّىٰ وَمِنكُم مَّن يُرَدُّ إِلَىٰ أَرْذَلِ الْعُمُرِ لِكَيْلَا يَعْلَمَ مِن بَعْدِ عِلْمٍ شَيْئًا ۚ وَتَرَى الْأَرْضَ هَامِدَةً فَإِذَا أَنزَلْنَا عَلَيْهَا الْمَاءَ اهْتَزَّتْ وَرَبَتْ وَأَنبَتَتْ مِن كُلِّ زَوْجٍ بَهِيجٍ }

Ẹ̀yin ènìyàn, tí ẹ bá wà nínú iyèméjì nípa àjíǹde, dájúdájú Àwa ṣẹ̀dá yín láti inú erùpẹ̀, lẹ́yìn náà láti inú àtọ̀, lẹ́yìn náà láti inú ẹ̀jẹ̀ dídì, lẹ́yìn náà láti inú báàṣí ẹran tí ó pé ní ẹ̀dá àti èyí tí kò pé ní ẹ̀dá nítorí kí A lè ṣàlàyé (agbára Wa) fun yín. A sì ń mú ohun tí A bá fẹ́ dúró sínú àpò ìbímọ títí di gbèdéke àkókò kan. Lẹ́yìn náà, A óò mu yín jáde ní òpóǹló. Lẹ́yìn náà, (ẹ óò máa ṣẹ̀mí lọ) nítorí kí ẹ lè sánn̄gun dópin agbára yín. Ẹni tí ó máa kú (ní kékeré) wà nínú yín. Ó sì wà nínú yín ẹni tí A óò dá (ìṣẹ̀mí) rẹ̀ sí di àsìkò ogbó kùjọ́kùjọ́ nítorí kí ó má lè mọ̀ ǹǹkan kan mọ́ lẹ́yìn tí ó ti mọ̀ ọ́n. Àti pé o máa rí ilẹ̀ ní gbígbẹ. Nígbà tí A bá sì sọ òjò kalẹ̀ lé e lórí, ó máa yíra padà. Ó máa gbèrú. Ó sì máa mú gbogbo oríṣiríṣi irúgbìn t'ó dára jáde. [Al-Hajj 5]

Ibo ni ọmọniyan maa ṣẹri padà sí, kini ẹsan olùṣe-rere àti alaburu lẹ́yìn isẹmi yii, a ti dárúkọ àwọn ẹri lórí ọrọ yii ṣíwájú nínú ipinrọ ti nọ́mbà rẹ̀ jẹ́ (20), ǹjẹ́ ayé yìí kan wà lásán nípasẹ̀ anfaani ni abi bibẹ rẹ ni ìdí pàtàkì kan? Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ أَوَلَمْ يَنظُرُوا فِي مَلَكُوتِ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَمَا خَلَقَ اللَّهُ مِن شَيْءٍ وَأَنْ عَسَىٰ أَن يَكُونَ قَدِ اقْتَرَبَ أَجَلُهُمْ ۖ فَبِأَيِّ حَدِيثٍ بَعْدَهُ يُؤْمِنُونَ}

Ṣé wọn kò wo ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ pẹ̀lú gbogbo n̄ǹkan tí Allāhu dá? Àmọ́ sá ó lè jẹ́ pé Àkókò ikú wọn ti súnmọ́. Nígbà náà, ọ̀rọ̀ wo ni wọn yóò gbàgbọ́ lẹ́yìn rẹ̀? Al-A'roof: 185 Allah tun sọ pe:

{ أَفَحَسِبْتُمْ أَنَّمَا خَلَقْنَاكُمْ عَبَثًا وَأَنَّكُمْ إِلَيْنَا لَا تُرْجَعُونَ}

Ṣé ẹ lérò pé A kàn ṣẹ̀dá yín fún ìranù ni, àti pé dájúdájú wọn ò níí da yín padà sọ́dọ̀ Wa?" Suuratul Muh'minuun: 115.

Alukurani jẹ nnkan ti a sọ titi di òní pẹ̀lú èdè ti o fi sọkalẹ, Olohun ti ola Re ga so pe:

{إِنَّا نَحْنُ نَزَّلْنَا الذِّكْرَ وَإِنَّا لَهُ لَحَافِظُونَ }

"Dajudaju Awa (Ọlọhun Allah) ni a sọ Iranti (Alukurani) kalẹ, dajudaju awa naa ni Oludaabo bo o. Al-Hijr 9 Arafi kan ko dínkù ninu ẹ, o si soro ki itakora wa nínú ẹ, tàbí adinku tabi jijirọ, Olohun ti ola Re ga so pe:

{أَفَلَا يَتَدَبَّرُونَ الْقُرْآنَ ۚ وَلَوْ كَانَ مِنْ عِندِ غَيْرِ اللَّهِ لَوَجَدُوا فِيهِ اخْتِلَافًا كَثِيرًا}

Ṣé wọn kò ronú nípa al-Ḱur'ān ni? Tí ó bá jẹ́ pé ó wá láti ọ̀dọ̀ ẹlòmíìràn yàtọ̀ sí Allāhu, wọn ìbá rí ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ ìtakora nínú rẹ̀. An-Nisaa 82 Nnkan ti wọn tẹ jáde ti wọn si pin káàkiri ni, Tira ńlá ni tii ko agara ba

ẹni tí ó bá fẹ́ mú irú rẹ̀ wá, o lẹtọ si láti maa ka a tàbí láti máa tẹti si i tabi lati máa ka ìtumọ̀ rẹ̀ ti wọn tu si èdè míràn. Gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ naa ni a ṣe ṣọ sunna Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati ẹkọ rẹ ati ìtàn ìgbésí ayé rẹ, ti wọn si gbe e de ọdọ wa ni ìbámu si sisẹntẹle àwọn ti wọn maa n gba ìtàn wa ti a le fi ọkàn tan. Wọn tẹ oun naa jáde pẹ̀lú èdè Lárúbáwá ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ, wọn si túmọ̀ rẹ̀ si èdè tí ó pọ. Alukurani ati Sunna, méjèèjì naa ni ipilẹkan ṣoṣo fun àwọn ìdájọ́ ati ofin Islam, a kii mu Islam latara ìwà àwọn Musulumi, ibi ti a ti maa n mu u naa ni imisi ti ọdọỌlọhun ti ko le si àṣìṣe níbẹ̀, oun naa ni Kuraani ati Sunna Anọbi Muhammad (kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a). Ọlọhun sọ nípa Kuraani pe

{ إِنَّ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْ بِٱلذِّكۡرِ لَمَّا جَآءَهُمۡۖ وَإِنَّهُۥ لَكِتَٰبٌ عَزِيزٞ - لَّا يَأۡتِيهِ ٱلۡبَٰطِلُ مِنۢ بَيۡنِ يَدَيۡهِ وَلَا مِنۡ خَلۡفِهِۦۖ تَنزِيلٞ مِّنۡ حَكِيمٍ حَمِيدٖ}

Dájúdájú àwọn t’ó ṣàì gbàgbọ́ nínú Tírà Ìrántí náà (ìyẹn, al-Ḱur’ān) nígbà tí ó dé bá wọn (ẹni ìparun ni wọ́n.) Dájúdájú òhun mà ni Tírà t’ó lágbára. Ìbàjẹ́ kò níí kàn án láti iwájú rẹ̀ àti láti ẹ̀yìn rẹ̀. Ìmísí tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ ni láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́gbọ́n, Ẹlẹ́yìn Fussilat: 41 42 Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ nípa Sunna pe Imisi lati ọdọ Ọlọhun ni:

{وَمَآ ءَاتَىٰكُمُ ٱلرَّسُولُ فَخُذُوهُ وَمَا نَهَىٰكُمۡ عَنۡهُ فَٱنتَهُواْۚ وَٱتَّقُواْ ٱللَّهَۖ إِنَّ ٱللَّهَ شَدِيدُ ٱلۡعِقَابِ}

Ohunkóhun tí Òjíṣẹ́ bá fun yín, ẹ gbà á. Ohunkóhun tí ó bá sì kọ̀ fun yín, ẹ jáwọ́ nínú rẹ̀. Kí ẹ sì bẹ̀rù Allāhu. Dájúdájú Allāhu le níbi ìyà. Al-Hash'r: 7

## 29. Islam n pàṣẹṣíṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì kódà ki wọn ma jẹ Musulumi, o si tun pàṣẹṣíṣe dáadáa si awọn ọmọ náà pẹ̀lú.

Islam n pàṣẹṣíṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Olúwa rẹ pàṣẹ pé:

{وَقَضَىٰ رَبُّكَ أَلَّا تَعْبُدُوا إِلَّا إِيَّاهُ وَبِالْوَالِدَيْنِ إِحْسَانًا ۚ إِمَّا يَبْلُغَنَّ عِندَكَ الْكِبَرَ أَحَدُهُمَا أَوْ كِلَاهُمَا فَلَا تَقُل لَّهُمَا أُفٍّ وَلَا تَنْهَرْهُمَا وَقُل لَّهُمَا قَوْلًا كَرِيمًا }

Olúwa rẹ pàṣẹ pé: "Ẹ má ṣe jọ́sìn fún ẹnì kan àyàfi Òun. Kí ẹ sì ṣe dáadáa sí àwọn òbí (yín) méjèèjì. Tí ọ̀kan nínú àwọn méjèèjì tàbí ìkíní kejì wọn bá dàgbà sí ọ lọ́dọ̀, má ṣe ṣíọ̀ sí wọn, má ṣe jágbe mọ́ wọn. Máa bá àwọn méjèèjì sọ ọ̀rọ̀ àpọ́nlé. Al-Isroo: 23 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَوَصَّيْنَا الْإِنسَانَ بِوَالِدَيْهِ حَمَلَتْهُ أُمُّهُ وَهْنًا عَلَىٰ وَهْنٍ وَفِصَالُهُ فِي عَامَيْنِ أَنِ اشْكُرْ لِي وَلِوَالِدَيْكَ إِلَيَّ الْمَصِيرُ }

Àti pé A pa á ní àṣẹ fún ènìyàn nípa àwọn òbí rẹ̀ méjèèjì - ìyá rẹ̀ gbé e ká (nínú oyún) pẹ̀lú àìlera lórí àìlera, ó sì gba ọmú lẹ́nu rẹ̀ láàrin ọdún méjì – (A sọ) pé: "Dúpẹ́ fún Èmi àti àwọn òbí rẹ méjèèjì." Ọ̀dọ̀ Mi sì ni àbọ̀ ẹ̀dá. Luqman: 14 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَوَصَّيْنَا الْإِنسَانَ بِوَالِدَيْهِ إِحْسَانًا ۖ حَمَلَتْهُ أُمُّهُ كُرْهًا وَوَضَعَتْهُ كُرْهًا ۖ وَحَمْلُهُ وَفِصَالُهُ ثَلَاثُونَ شَهْرًا ۚ حَتَّىٰ إِذَا بَلَغَ أَشُدَّهُ وَبَلَغَ أَرْبَعِينَ سَنَةً قَالَ رَبِّ أَوْزِعْنِي أَنْ أَشْكُرَ نِعْمَتَكَ الَّتِي أَنْعَمْتَ عَلَيَّ وَعَلَىٰ وَالِدَيَّ وَأَنْ أَعْمَلَ صَالِحًا تَرْضَاهُ وَأَصْلِحْ لِي فِي ذُرِّيَّتِي ۖ إِنِّي تُبْتُ إِلَيْكَ وَإِنِّي مِنَ الْمُسْلِمِينَ }

A pa á ní àsẹ fún ènìyàn pé kí ó máa ṣe dáadáa sí àwọn òbí rẹ méjèèjì. Ìyá rẹ ní oyún rẹ pẹ̀lú wàhálà. Ó sì bí i pẹ̀lú wàhálà. Oyún rẹ àti gbígba ọmú lẹ́nu rẹ jẹ́ ọgbọ̀n oṣù. (Ó sì ń tọ́ ọ) títí ó fi dàgbà, tí ó fi di ọmọ ogójì ọdún, ó sì sọ pé: "Olúwa mi, fi mọ̀ mí kí n̄g máa dúpẹ́ ìdẹ̀ra Rẹ, èyí tí Ó fi ṣe ìdẹ̀ra fún mi àti fún àwọn òbí mi méjèèjì, kí n̄g sì máa ṣe iṣẹ́ rere, èyí tí O yọ́nú sí. Kí O sì ṣe rere fún mi lórí àwọn àrọ́mọdọ́mọ mi. Dájúdájú èmi ti ronú pìwàdà sí ọ̀dọ̀ Rẹ. Dájúdájú èmi sì wà nínú àwọn mùsùlùmí." Al-Ah'qoof: 15

وعَنْ أَبِي هُرَيْرَةَ رَضِيَ اللَّهُ عَنْهُ قَالَ: جَاءَ رَجُلٌ إِلَى رَسُولِ اللَّهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَقَالَ: يَا رَسُولَ اللَّهِ مَنْ أَحَقُّ النَّاسِ بِحُسْنِ صَحَابَتِي؟ قَالَ: «أُمُّكَ» قَالَ: ثُمَّ مَنْ؟ قَالَ: «ثُمَّ أُمُّكَ» قَالَ: ثُمَّ مَنْ؟ قَالَ: «ثُمَّ أُمُّكَ» قَالَ: ثُمَّ مَنْ؟ قَالَ: «ثُمَّ أَبُوكَ»

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọ́nú si i- o sọ pe: Arákùnrin kan wa ba OjiṣẹỌlọhun- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- o ba sọ pe: Irẹ OjiṣẹỌlọhun, tani o lẹtọ si ki n maa fi dáadáa ba a lo pọ jù nínú àwọn èèyàn? O sọ pe: "Iya rẹ", o sọ pe: Leyin naa tani? O sọ pe: "Leyin naa iya rẹ", o sọ pe: Lẹ́yìn náà tani? O sọ pe: "Lẹ́yìn náà iya rẹ", o so pe: Lẹ́yìn náà tani? O sọ pe: "Lẹ́yìn náà bàbá rẹ". Sohiihu ti Muslim

Àṣẹṣíṣe dáadáa si awọn òbí yii wa fun gbogbo òbí, bóyá wọn jẹ Musulumi ni abi wọn kii ṣe Musulumi.

فعَنْ أَسْمَاءَ بِنْتِ أَبِي بَكْرٍ قَالَتْ: (قَدِمَتْ أُمِّي وَهِيَ مُشْرِكَةٌ فِي عَهْدِ قُرَيْشٍ وَمُدَّتِهِمْ إِذْ عَاهَدُوا النَّبِيَّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ مَعَ ابْنِهَا فَاسْتَفْتَيْتُ النَّبِيَّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَقُلْتُ: إِنَّ أُمِّي قَدِمَتْ وَهِيَ رَاغِبَةٌ، أَفَأَصِلُهَا؟ قَالَ: «نَعَمْ صِلِي أُمَّكِ»

Lati ọdọ Asmaa ọmọbìnrin Abubakr, o sọ pe: "Iya mi ti o jẹ ọṣẹbọ wa ba mi pẹ̀lú ọmọkùnrin rẹ ni asiko ti àwọn Kureeṣi gbe àdéhùn pẹ̀lú Anọbi Muhammad- ki

ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mo wa bi Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- léèrè pe:" Iya mi wa ba mi, o si n fẹ ki n ṣe dáadáa si oun, ṣe ki n ṣe e si i? O sọ pe:" Bẹẹni, ṣe dáadáa si i". Sohiihul-Bukhaariy Ti àwọn òbí rẹ ba wa gbìyànjú láti jẹ ki o fi Islam silẹ bọ sínú Kèfèrí, Islam n pa a láṣẹ pe ko gbọdọ tẹle wọn nibi ìyẹn, àmọ́ ki o ṣi maa ṣe dáadáa si wọn. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ وَإِن جَٰهَدَاكَ عَلَىٰٓ أَن تُشْرِكَ بِي مَا لَيْسَ لَكَ بِهِۦ عِلْمٌ فَلَا تُطِعْهُمَاۖ وَصَاحِبْهُمَا فِي ٱلدُّنْيَا مَعْرُوفًاۖ وَٱتَّبِعْ سَبِيلَ مَنْ أَنَابَ إِلَيَّۚ ثُمَّ إِلَيَّ مَرْجِعُكُمْ فَأُنَبِّئُكُم بِمَا كُنتُمْ تَعْمَلُونَ}

Tí àwọn méjèèjì bá sì jà ọ́ lógun pé kí ó fi ohun tí ìwọ kò ní ìmọ̀ nípa rẹ̀ ṣẹbọ sí Mi, má ṣe tẹ̀lé àwọn méjèèjì.1 Fi dáadáa bá àwọn méjèèjì lò pọ̀ ní ilé ayé. Kí o sì tẹ̀lé ojú ọ̀nà ẹni tí ó bá ṣẹ́rí padà sí ọ̀dọ̀ Mi (ní ti ìronúpìwàdà). Lẹ́yìn náà, ọ̀dọ̀ Mi ni ibùpadàsí yín. Nítorí náà, Mo máa fun yín ní ìró ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́. Luqman: 15

Islam ko kọ fun Musulumi láti máa ṣe daadaa si mọlẹbi rẹ ti wọn jẹọṣẹbọ tabi awọn ti wọn kii ṣe mọlẹbi rẹ lópin ìgbà ti wọn ko ba ti gbógun ti i. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ لَّا يَنْهَاكُمُ اللَّهُ عَنِ الَّذِينَ لَمْ يُقَاتِلُوكُمْ فِي الدِّينِ وَلَمْ يُخْرِجُوكُم مِّن دِيَارِكُمْ أَن تَبَرُّوهُمْ وَتُقْسِطُوا إِلَيْهِمْ ۚ إِنَّ اللَّهَ يُحِبُّ الْمُقْسِطِينَ }

Allāhu kò kọ̀ fun yín nípa àwọn tí kò gbé ogun tì yín nípa ẹ̀sìn, tí wọn kò sì lé yín jáde kúrò nínú ìlú yín, pé kí ẹ ṣe dáadáa sí wọn, kí ẹ sì ṣe déédé sí wọn. Dájúdájú Allāhu fẹ́ràn àwọn olùṣe-déédé. Al-Mum'tahanah: 8

Islam n pàṣẹṣíṣe dáadáa si awọn ọmọ, àṣẹ ti o tóbi ju ti Islām n pa bàbá náà ni ki o fi iwọ ti Ọlọhun ni lori awọn ọmọ rẹ mọ won, gẹgẹ bi Ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ṣe sọ fun ọmọọmọ-ìyá baba rẹ tii ṣe Abdullaah ọmọ Abbaas- ki Ọlọhun yọnu si i- pe:

«يَا غُلامُ أَوْ يَا غُلَيِّمُ أَلا أُعَلِّمُكَ كَلِمَاتٍ يَنْفَعُكَ اللهُ بِهِنَّ؟ فَقُلْتُ: بَلَى. فَقَالَ: "احْفَظِ اللهَ يَحْفَظْكَ احْفَظِ اللهَ تَجِدْهُ أَمَامَكَ تَعَرَّفْ إِلَيْهِ فِي الرَّخَاءِ يَعْرِفْكَ فِي الشِّدَّةِ وَإِذَا سَأَلْتَ فَاسْأَلِ اللهَ وَإِذَا اسْتَعَنْتَ فَاسْتَعِنْ بِاللهِ»

"Irẹ ọmọdékùnrin yìí, tabi irẹ ọmọdékùnrin kékeré yìí, ṣe ki n kọ ẹ ni àwọn gbólóhùn kan ti Ọlọhun a jẹ ki o ṣe àǹfààní fun ẹ? Ni mo ba sọ pe: Bẹẹni, o sọ pe:"Sọ Ọlọhun, Ọlọhun yoo ṣọ ìwọ naa, ṣọ Ọlọhun, waa ri I ni iwájú rẹ, jẹ ki Ọlọhun mọ ọ ni ìgbà ti ara ba dẹ ọ, Oun náà yóò mọ ọ nígbà ilekoko, ti o ba fẹ béèrè nkan, Ọlọhun ni ki o bi, ti o ba fẹ wa iranlọwọ, Ọlọhun ni ki o wa iranlọwọ Rẹ". Ahmad ni o gba a wa 4/287

Ọlọhun pa àwọn òbí méjèèjì láṣẹ pé ki wọn kọ àwọn ọmọ wọn ni nkan ti yóò ṣe wọ́n ni anfaani ninu alaamọri ẹ̀sìn wọn ati ayé wọn. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọpe:

{ يَٰٓأَيُّهَا ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ قُوٓاْ أَنفُسَكُمۡ وَأَهۡلِيكُمۡ نَارٗا وَقُودُهَا ٱلنَّاسُ وَٱلۡحِجَارَةُ عَلَيۡهَا مَلَٰٓئِكَةٌ غِلَاظٞ شِدَادٞ لَّا يَعۡصُونَ ٱللَّهَ مَآ أَمَرَهُمۡ وَيَفۡعَلُونَ مَا يُؤۡمَرُونَ}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ ṣọ́ ẹ̀mí ara yín àti àwọn ará ilé yín níbi Iná. Ènìyàn àti òkúta ni n̄ǹkan ìkoná rẹ̀. Àwọn mọlāika t'ó rorò, tí wọ́n le ni ẹ̀ṣọ́ rẹ̀. Wọn kò níí yapa àṣẹ Allāhu níbi ohun tí Ó bá pa láṣẹ fún wọn. Wọ́n sì ń ṣe ohun tí wọ́n bá pa láṣẹ fún wọn. Suuratut-Tah'riim: 6 Lati ọdọ Aliy- ki Ọlọhun yọ́nú si i- nibi gbólóhùn Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ti O sọ pe:

{قُوا أَنفُسَكُمْ وَأَهْلِيكُمْ نَارًا }

{ẹ ṣọ́ ẹ̀mí ara yín àti àwọn ará ilé yín níbi Iná} O n sọ pe: "Ẹ kọ wọn ni ẹkọ, ẹ fi ìmọ̀ mọ wọn" Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- pa bàbá láṣẹ láti kọọmọ rẹ ni Irun; ki o le gba rírè lórí ẹ. Anọbi- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

(مُرُوا أولاكمِ بالصلاةِ وهم أبناءُ سبعِ سِنينَ)

(Ẹ maa pa àwọn ọmọ yin láṣẹ láti maa kírun ti wọn ba ti pé ọmọ ọdún méje) Abu Daud ni o gba a wa. O tun sọ– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– pe:

«كُلُّكُمْ رَاعٍ وَكُلُّكُمْ مَسْؤولٌ عَنْ رَعِيَّتِهِ الإِمَامُ رَاعٍ وَمَسْؤولٌ عَنْ رَعِيَّتِهِ وَالرَّجُلُ رَاعٍ فِي أَهْلِهِ وَهُوَ مَسْؤولٌ عَنْ رَعِيَّتِهِ وَالمَرْأَةُ رَاعِيَةٌ فِي بَيْتِ زَوْجِهَا وَمَسْؤولَةٌ عَنْ رَعِيَّتِهَا والخادمُ راعٍ في مالِ سيِّدِه ومسؤولٌ عن رعيَّتِه وكلُّكم راعٍ ومسؤولٌ عن رعيَّتِه»

"Gbogbo yin ni alamojuto, gbogbo yin si ni a maa bi leere nípa nkan ti a ni ki ẹ mojuto. Alamojuto ni adarí, a si maa bi i léèrè nipa àwọn ti o mojuto, alamojuto ni ọkùnrin jẹ fun awon ará-ilé rẹ, a si maa bi i léèrè nípa àwọn ti o n mojuto, alamojuto ni obìnrin jẹ ni ilé ọkọ rẹ, a si maa bi i léèrè nípa nnkan ti o mojuto, alamojuto ni ọmọ-ọdọ jẹ fun dúkìá olówó rẹ, a si maa bi i léèrè nípa nkan ti o mojuto, gbogbo yin pátá ni alamojuto, a si maa bi yin léèrè nípa nkan ti e mojuto" Sọhiihu Ibnu Hibbaan 4490

Islam pa bàbá láṣẹ láti maa náwó lórí àwọn ọmọ rẹ̀ ati awọn ará-ilé rẹ, a si ti sọ nkan ti o jẹ mọ́ bayẹn nibi ipinrọ (18), Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ṣàlàyé ọlá ti o n bẹ fun ninawo lórí ọmọ, o sọ pe:

«أَفْضَلُ دِينَارٍ يُنْفِقُهُ الرَّجُلُ: دِينَارٌ يُنْفِقُهُ عَلَى عِيَالِهِ وَدِينَارٌ يُنْفِقُهُ الرَّجُلُ عَلَى دَابَّتِهِ فِي سَبِيلِ اللهِ وَدِينَارٌ يُنْفِقُهُ عَلَى أَصْحَابِهِ فِي سَبِيلِ اللهِ». قَالَ أَبُو قِلَابَةَ: " وَبَدَأَ بِالْعِيَالِ ثُمَّ قَالَ أَبُو قِلَابَةَ: وَأَيُّ رَجُلٍ أَعْظَمُ أَجْرًا مِنْ رَجُلٍ يُنْفِقُ عَلَى عِيَالٍ صِغَارٍ يُعِفُّهُمْ أَوْ يَنْفَعُهُمُ اللهُ بِهِ وَيُغْنِيهِمْ"

"Diinaari ti o lọla ju ti ọmọkùnrin maa n na ni: Diinaari ti o n na fun àwọn ti o n bọ́, ati diinaari ti o n ná fun nkan-ògùn rẹ ni ojú ọ̀nà Ọlọhun, ati diinaari ti o n ná fún àwọn ọ̀rẹ́ rẹ ni ojú ọ̀nà Ọlọhun". Abu Qilaaba wa sọ pe: O bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn tí èèyàn n bọ́, lẹ́yìn náà Abu Qilaaba wa sọ pé: Ọkùnrin wo wa ni laada rẹ yóò tóbi ju ti ẹni tí n náwó fún àwọn ọmọ kéékèèké ti o n bọ́ ti wọn ko fi nii maa ṣe nkan ti kò tọ́, tabi ki Ọlọhun jẹ ki wọn fi wúlò, tabi ki o rọ̀ wọn lọ́rọ̀ Sohiihu Muslim: 994

## 30. Islām n pàṣẹ déédéé nibi ọ̀rọ̀ ati iṣẹ́ pẹ̀lú àwọn èèyàn títí tí ó fi dé orí àwọn ọ̀tá.

Ìròyìn déédéé n bẹ fun Ọlọhun níbi ìṣe ati ṣíṣètò Rẹ láàrin àwọn ẹrú Rẹ, O si wa ni oju ọna tí o tọ́ nibi nnkan ti O pàṣẹ rẹ ati nibi nnkan ti O kọ̀, ati nibi nnkan ti O dá, ati nibi nnkan ti O kádàrá, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{شَهِدَ اللَّهُ أَنَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ وَالْمَلَائِكَةُ وَأُولُو الْعِلْمِ قَائِمًا بِالْقِسْطِ ۚ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ الْعَزِيزُ الْحَكِيمُ}

Allāhu jẹ́rìí pé dájúdájú kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Àwọn mọlāika àti onímọ̀ ẹ̀sìn (tún jẹ́rìí bẹ́ẹ̀.), Allāhu ni Onídéédé. Kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Aal Im’raan/18 Ọlọhun n pàṣẹ déédéé, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{قُلْ أَمَرَ رَبِّي بِالْقِسْطِ}

Sọ pé: “Olúwa mi p’àṣẹ ṣíṣe déédé. Al-A'roof: 29 Gbogbo àwọn Ojiṣẹ ati awọn Anọbi pátá- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn- ni wọn mu déédéé wá, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{لَقَدْ أَرْسَلْنَا رُسُلَنَا بِالْبَيِّنَاتِ وَأَنزَلْنَا مَعَهُمُ الْكِتَابَ وَالْمِيزَانَ لِيَقُومَ النَّاسُ بِالْقِسْطِ }

Dájúdájú A fi àwọn ẹ̀rí t’ó yanjú rán àwọn Òjíṣẹ́ Wa. A sọ Tírà kalẹ̀ fún wọn àti òṣùwọ̀n nítorí kí àwọn ènìyàn lè rí déédé ṣe (láààrin ara wọn). Al-Hadiid: 25 Òṣùwọ̀n náà ni déédéé nibi ọ̀rọ̀ àti ìṣe.

Islam n pàṣẹ ki a ṣe déédéé si gbogbo àwọn ènìyàn níbi ọ̀rọ̀ àti iṣẹ́, kódà ti o fi dórí àwọn ọ̀tá.

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا كُونُوا قَوَّامِينَ بِالْقِسْطِ شُهَدَاءَ لِلَّهِ وَلَوْ عَلَىٰ أَنفُسِكُمْ أَوِ الْوَالِدَيْنِ وَالْأَقْرَبِينَ ۚ إِن يَكُنْ غَنِيًّا أَوْ فَقِيرًا فَاللَّهُ أَوْلَىٰ بِهِمَا ۖ فَلَا تَتَّبِعُوا الْهَوَىٰ أَن تَعْدِلُوا ۚ وَإِن تَلْوُوا أَوْ تُعْرِضُوا فَإِنَّ اللَّهَ كَانَ بِمَا تَعْمَلُونَ خَبِيرًا}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ jẹ́ olùdúró ṣinṣin lórí òdodo nígbà tí ẹ bá ń jẹ́rìí nítorí ti Allāhu, kódà kí (ẹ̀rí jíjẹ́ náà) tako ẹ̀yin fúnra yín tàbí àwọn òbí méjèèjì àti àwọn ẹbí; yálà ó jẹ́ ọlọ́rọ̀ tàbí aláìní. Allāhu súnmọ́ (yín) ju àwọn méjèèjì lọ. Nítorí náà, ẹ má ṣe tẹ̀lé ìfẹ́-inú láti má ṣe déédé. Tí ẹ bá yí ojú-ọ̀rọ̀ sódì tàbí tí ẹ bá gbúnrí kúrò (níbi déédé), dájúdájú Allāhu ń jẹ́ Alámọ̀tán nípa ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́. An-Nisaa: 135 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَلَا يَجْرِمَنَّكُمْ شَنَآنُ قَوْمٍ أَن صَدُّوكُمْ عَنِ الْمَسْجِدِ الْحَرَامِ أَن تَعْتَدُوا ۘ وَتَعَاوَنُوا عَلَى الْبِرِّ وَالتَّقْوَىٰ ۖ وَلَا تَعَاوَنُوا عَلَى الْإِثْمِ وَالْعُدْوَانِ ۚ وَاتَّقُوا اللَّهَ ۖ إِنَّ اللَّهَ شَدِيدُ الْعِقَابِ}

Ẹ má ṣe jẹ́ kí ìkórira àwọn ènìyàn kan tì yín láti tayọ ẹnu-àlà nítorí pé wọ́n ṣe yín lórí kúrò ní Mọ́sálásí Haram. Ẹ ran ara yín lọ́wọ́ lórí iṣẹ́ rere àti ìbẹ̀rù Allāhu. Ẹ má ṣe ran ara yín lọ́wọ́ lórí (ìwà) ẹ̀ṣẹ̀ àti ìtayọ ẹnu-àlà. Ẹ bẹ̀rù Allāhu. Dájúdájú Allāhu le (níbi) ìyà. Al-Maa'ida: 2 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا كُونُوا قَوَّامِينَ لِلَّهِ شُهَدَاءَ بِالْقِسْطِ ۖ وَلَا يَجْرِمَنَّكُمْ شَنَآنُ قَوْمٍ عَلَىٰ أَلَّا تَعْدِلُوا ۚ اعْدِلُوا هُوَ أَقْرَبُ لِلتَّقْوَىٰ}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, nítorí ti Allāhu ẹ jẹ́ olùdúró ṣinṣin lórí òdodo nígbà tí ẹ bá ń jẹ́rìí. Ẹ má ṣe jẹ́ kí ìkórira àwọn ènìyàn kan tì yín láti má ṣe déédé. Ẹ ṣe déédé, òhun l'ó súnmọ́ ìbẹ̀rù Allāhu jùlọ. Al-Maa'ida: 8 Ǹjẹ́ o le ri iru pipaṣẹ jíjẹ́rìí òdodo ati ọrọ òdodo yii nínú àwọn òfin àwọn ìjọ òde òní tabi nínú àwọn ẹsin ti àwọn èèyàn n sìn bi, kódà ki o jẹ pe èèyàn maa jẹ́rìí le ara rẹ lórí tabi lórí àwọn òbí rẹ tàbí lori awọn mọ̀lẹ́bí rẹ, njẹ o tun le ri pipaṣẹ déédéé pẹ̀lú ọ̀tá àti ọ̀rẹ́ nínú wọn bi.

Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- pàṣẹ déédéé láàárín àwọn ọmọ

فعَنْ عَامِرٍ قَالَ: سَمِعْتُ النُّعْمَانَ بْنَ بَشِيرٍ رَضِيَ اللَّهُ عَنْهُمَا وَهُوَ عَلَى المِنْبَرِ يَقُولُ: أَعْطَانِي أَبِي عَطِيَّةً فَقَالَتْ عَمْرَةُ بِنْتُ رَوَاحَةَ: لاَ أَرْضَى حَتَّى تُشْهِدَ رَسُولَ اللَّهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَأَتَى رَسُولَ اللَّهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَقَالَ: إِنِّي أَعْطَيْتُ ابْنِي مِنْ عَمْرَةَ بِنْتِ رَوَاحَةَ عَطِيَّةً فَأَمَرَتْنِي أَنْ أُشْهِدَكَ يَا رَسُولَ اللَّهِ قَالَ: «أَعْطَيْتَ سَائِرَ وَلَدِكَ مِثْلَ هَذَا؟» قَالَ: لاَ قَالَ: «فَاتَّقُوا اللَّهَ وَاعْدِلُوا بَيْنَ أَوْلاَدِكُمْ» قَالَ: فَرَجَعَ فَرَدَّ عَطِيَّتَهُ)

Lati ọdọ Aamir, o sọ pe: Mo gbọ ti An-Nu'maan ọmọ Basheer- ki Ọlọhun yọ́nú si awọn méjèèjì- n sọ lori Munbari pe: Bàbá mi fun mi ni ẹbun kan, ni Amrat

ọmọbìnrin Rowaahat wa sọ pé: Mi o nii yọ́nú si i titi ti wàá fi fi Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- jẹ́rìí si i. Ni o ba wa ba Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- o wa sọ pe: Mo fun ọmọ mi ti Amrat ọmọbìnrin Rowaahat bi fun mi ni ẹ̀bùn, ni Amrat wa pa mi láṣẹ pe ki n fi ìwọ Ojiṣẹ Ọlọhun jẹ́rìí si i, Ojiṣẹ Ọlọhun wa sọ pé: "Ǹjẹ́ gbogbo àwọn ọmọ rẹ to ṣẹku ni o fun ni irú èyí?" O sọ pe: Rara, O sọ pe: "Ẹ páyà Ọlọhun, ki ẹ si ṣe déédéé láàárín àwọn ọmọ yín". O sọ pe: O padà, o si da ẹ̀bùn rẹ padà. Sohiihu ti Al-Bukhaari 2587

Ìyẹn ni pe ọ̀rọ̀ àwọn èèyàn àti ìlú ko le ni ojútùú àyàfi pẹ̀lú déédéé, àwọn ènìyàn ko le ni ifayabalẹ lórí ẹsin wọn, ati ẹjẹ wọn, àti àwọn ọmọ wọn, ati ọmọlúwàbí wọn, ati dúkìá wọn, ati awọn ìlú wọn, àyàfi pẹ̀lú déédéé, tori ẹ ni o ṣe jẹ pe nígbà tí àwọn Kèfèrí Mẹ́kà fún ilẹ̀ mọ àwọn Musulumi nínú ìlú Mẹ́kà, Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- pa wọn láṣẹ lati ṣe hijira lọ si ìlú Ábáṣà, o si sọ ìdí ti o fi ni ki wọn lọ si ìlú naa, toripe ọba onidéédéé wa nibẹ ti kii gba ki wọn ṣe àbòsí fun ẹnikan kan ni ọdọ rẹ.

## Islām n pàṣẹ ṣíṣe dáadáa si gbogbo ẹ̀dá pátá, o si n pèpè lọ síbi àwọn ìwà dáadáa àti àwọn iṣẹ́ rere.

Islām n pàṣẹ ṣíṣe dáadáa si gbogbo ẹ̀dá pátá, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{إِنَّ اللَّهَ يَأْمُرُ بِالْعَدْلِ وَالْإِحْسَانِ وَإِيتَاءِ ذِي الْقُرْبَىٰ }

Dájúdájú Allāhu ń pàṣẹ ṣíṣe déédée, ṣíṣe rere àti fífún ẹbí (ní ǹǹkan). An-Nah'l 90 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{الَّذِينَ يُنفِقُونَ فِي السَّرَّاءِ وَالضَّرَّاءِ وَالْكَاظِمِينَ الْغَيْظَ وَالْعَافِينَ عَنِ النَّاسِ ۗ وَاللَّهُ يُحِبُّ الْمُحْسِنِينَ}

Àwọn t'ó ń ná owó wọn nígbà ìdẹ̀ra àti nígbà ìnira, àwọn tí ń gbé ìbínú mì, àwọn alámòjúúkúrò fún àwọn èniyàn níbi àṣìṣe; Allāhu nífẹ̀ẹ́ àwọn olùṣe-rere. Aal Im'raan/134 Ojiṣẹ Ọlọhun– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – sọ pe:

« إنَّ اللَّهَ كَتَبَ الإحْسَانَ علَى كُلِّ شيءٍ، فَإِذَا قَتَلْتُمْ فأحْسِنُوا القِتْلَةَ، وإذَا ذَبَحْتُمْ فأحْسِنُوا الذَّبْحَ، وَلْيُحِدَّ أَحَدُكُمْ شَفْرَتَهُ، فَلْيُرِحْ ذَبِيحَتَهُ »

"Dájúdájú Ọlọhun ti ṣe ṣíṣe dáadáa ni ọran-anyan lórí gbogbo nnkan, ti ẹ ba fẹ pa nnkan, ki ẹ pa a dáadáa, ti ẹ ba fẹ dú nnkan, ki ẹ du u dáadáa, ki ẹni kọọkan yin jẹ ki ọ̀bẹ rẹ mú dáadáa, ki o si tètè kó ìsinmi bá nnkan ti o fẹ́ dú" Sohiihu Muslim: 1955

Islam n pepe si ìwà dáadáa àti iṣẹ́ rere, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ nínú ìròyìn Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nínú àwọn Tírà ti o ṣíwájú pé:

{الَّذِينَ يَتَّبِعُونَ الرَّسُولَ النَّبِيَّ الْأُمِّيَّ الَّذِي يَجِدُونَهُ مَكْتُوبًا عِندَهُمْ فِي التَّوْرَاةِ وَالْإِنجِيلِ يَأْمُرُهُم بِالْمَعْرُوفِ وَيَنْهَاهُمْ عَنِ الْمُنكَرِ وَيُحِلُّ لَهُمُ الطَّيِّبَاتِ وَيُحَرِّمُ عَلَيْهِمُ الْخَبَائِثَ وَيَضَعُ عَنْهُمْ إِصْرَهُمْ وَالْأَغْلَالَ الَّتِي كَانَتْ عَلَيْهِمْ ۚ فَالَّذِينَ آمَنُوا بِهِ وَعَزَّرُوهُ وَنَصَرُوهُ وَاتَّبَعُوا النُّورَ الَّذِي أُنزِلَ مَعَهُ ۙ أُولَٰئِكَ هُمُ الْمُفْلِحُونَ}

Àwọn t'ó ń tẹ̀lé Òjíṣẹ́ náà, Ànábì aláìmọ̀ọ́nkọmọ̀ọ́nkà, ẹni tí wọ́n yóò bá àkọsílẹ̀ nípa rẹ̀ lọ́dọ̀ wọn nínú at-Taorāh àti al-'Injīl, tí ó ń pa wọ́n láṣẹ ohun rere, tí ó ń kọ ohun burúkú fún wọn, tí ó ń ṣe àwọn ǹǹkan dáadáa lẹ́tọ̀ọ́ fún wọn, tí ó sì ń ṣe àwọn ǹǹkan

àìdáa léèwọ̀ fún wọn, tí ó tún máa gbé ẹrù (àdéhùn t'ó wúwo) àti àjàgà t'ó ń bẹ lọ́rùn wọn kúrò fún wọn; àwọn t'ó gbàgbọ́ nínú rẹ̀, tí wọ́n bu iyì fún un, tí wọ́n ràn án lọ́wọ́, tí wọ́n sì tẹ̀lé ìmọ́lẹ̀ náà (ìyẹn, al-Ƙur'ān) tí A sọ̀kalẹ̀ fún un, àwọn wọ̀nyẹn ni olùjèrè. Al-A'rọọf 157
Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe:

«يَا عَائِشَةُ إِنَّ اللهَ رَفِيقٌ يُحِبُّ الرِّفْقَ وَيُعْطِي عَلَى الرِّفْقِ مَا لَا يُعْطِي عَلَى الْعُنْفِ وَمَا لَا يُعْطِي عَلَى مَا سِوَاهُ»

"Irẹ Aishat, dájúdájú Ọba ti O rọ̀ ni Ọlọhun, O si nífẹ̀ẹ́ si rírọ̀, O si maa n fún ni ní nnkan látàrí rírọ̀ nnkan ti Ko le fún ni látàrí líle ati nnkan ti Ko nii fún ni lórí nnkan ti o ba ti yàtò si i" Sohiihu Muslim: 2593 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«إِنَّ اللَّهَ حَرَّمَ عَلَيْكُمْ: عُقُوقَ الأُمَّهَاتِ وَوَأْدَ البَنَاتِ وَمَنَعَ وَهَاتِ وَكَرِهَ لَكُمْ قِيلَ وَقَالَ وَكَثْرَةَ السُّؤَالِ وَإِضَاعَةَ المَالِ»

"Dájúdájú Ọlọhun ṣe ni eewọ fun yin: Sísẹ àwọn ìyá, àti sísin àwọn ọmọbìnrin láàyè, ati kíkọ nnkan ti Ọlọhun ni ki á ná, ati bíbéèrè fun nnkan ti èèyàn ko ni ẹ̀tọ́ nínú ẹ, O si tun ṣe ni eewọ fún yin: gbọyi-sọyi, ati apọju ìbéèrè, ati rira owó láre" Sọhiihu ti Buhari 2408
Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«لَا تَدْخُلُونَ الْجَنَّةَ حَتَّى تُؤْمِنُوا وَلَا تُؤْمِنُوا حَتَّى تَحَابُّوا أَوَلَا أَدُلُّكُمْ عَلَى شَيْءٍ إِذَا فَعَلْتُمُوهُ تَحَابَبْتُمْ؟ أَفْشُوا السَّلَامَ بَيْنَكُمْ»

"Ẹ o nii wọ Alujanna títí tí ẹ fi máa gbagbọ, ẹ o nii gbagbọ títí tí ẹ fi maa nífẹ̀ẹ́ ara yín, ṣé ki n tọka yin si nkankan ti ẹ ba ti ṣe e, ẹ maa nífẹ̀ẹ́ ara yín? Ẹ maa fọn salamọ ka láàrin ara yín" Sọhiihu ti Muslim 54

## 32. Islam n pàṣẹ ki a ní àwọn ìwà ẹlẹyìn bíi òdodo, ati pípé àmàánnà, ati ìkóraró nibi nkan ti ko dára, ati ìtìjú, ati ìgboyà, ati ninawo, ati títọrẹ, ati ríran ẹni tí ó ní bukaata lọ́wọ́, àti ríran ẹni tí ó wa nínú ibanujẹ lọ́wọ́, àti bíbọ́ẹni tí ebi ń pa, ati jíjẹ́ alamuleti rere, ati dida ẹbí pọ̀, ati ki káàánú àwọn ẹranko.

Islam n pàṣẹ ki a ní àwọn ìwà ẹlẹyìn, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

(إِنَّمَا بُعِثْتُ لِأُتَمِّمَ صَالِحَ الْأَخْلَاقِ)

(Wọ́n gbé mi dìde láti pé àwọn ìwà tí ó dára) Sọhiihul Adabil Mufrad 207 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

(نَّ من أحبِّكم إليَّ ، وأقربِكم مني مجلسًا يومَ القيامةِ أحاسِنُكم أخلاقًا ، وإنَّ أبغضَكم إليَّ وأبعدَكم مني مجلسًا يومَ القيامةِ الثَّرثارونَ ، والمُتشدِّقونَ ، والمُتفيهقونَ ، قالوا : قد علِمْنا الثرثارونَ و المتشدِّقونَ ، فما المتفيهقونَ ؟ قال : المُتكبِّرونَ)

Dájúdájú nínú àwọn ti mo nífẹ̀ẹ́ si ju nínú yín, ti ibùjókòó wọn yoo si sunmọ mi ju ni ọjọ igbende, àwọn naa ni àwọn ti ìwà wọn dára jù nínú yin, àwọn ti mo sì korira ju nínú yín, ti ibùjókòó wọn yóò si jìnà si mi ju ni ọjọ́ igbende, àwọn naa ni àwọn ẹlẹ́jọ-wẹwẹ, ati awọn alasọtan-ọrọ, ati awọn al-mutafay'hiquun, wọn sọ pé: Irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, a ti mọ àwọn ẹlẹ́jọ-wẹwẹ ati awọn alasọtan-ọrọ, àwọn wo wa ni al-mutafay'hiquun? O sọ

pe: Àwọn naa ni àwọn onigberaga. As-Silsilatu As-Sohiiha 791

وعَنْ عَبْدِ اللَّهِ بْنِ عَمْرٍو رَضِيَ اللَّهُ عَنْهُمَا قَالَ: " لَمْ يَكُنِ النَّبِيُّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ فَاحِشًا وَلاَ مُتَفَحِّشًا" وَكَانَ يَقُولُ: (إِنَّ مِنْ خِيَارِكُمْ أَحْسَنَكُمْ أَخْلاَقًا)

Lati ọdọ Abdullah ọmọ Amr- ki Ọlọhun yọ́nú si awọn méjèèjì- o sọ pe: "Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- kii ṣe onisọkusọ, kii sii mọ̀-ọ́n-mọ̀ sọ isọkusọ", o maa n sọ pé: "Dájúdájú ninu awọn ti wọn lóore jù nínú yín náà ni àwọn ti ìwà wọn dára jù nínú yín". Sohiihu ti Al-Bukhaar 3559 Àti àwọn nnkan ti o yàtọ̀ si yẹn nínú àwọn Aaya ati Hadiisi ti o n tọ́ka si pé Islām n ṣeni lojukokoro ìwà rere àti iṣẹ́ rere lapapọ.

Nínú nnkan ti Islam n pàṣẹ rẹ náà ni: Ododo, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

(عَلَيْكُمْ بِالصِّدْقِ فَإِنَّ الصِّدْقَ يَهْدِي إِلَى الْبِرِّ وَإِنَّ الْبِرَّ يَهْدِي إِلَى الْجَنَّةِ وَمَا يَزَالُ الرَّجُلُ يَصْدُقُ وَيَتَحَرَّى الصِّدْقَ حَتَّى يُكْتَبَ عِنْدَ اللهِ صِدِّيقًا)

"Òdodo di ọwọ yin, torí pé òdodo máa n tọ́ni sọ́nà lọ sí dáadáa ni, dáadáa si máa n tọ́ni sọ́nà lọ sí Alijanna ni, ọmọniyan ko nii yé má sọ òdodo tí yóò sì máa wá òdodo kiri tìtí tí wọn fi máa kọ sí ọdọ Ọlọhun pé olódodo ni i" Sohiihu Muslim: 2607

Nínú nnkan ti Islam pàṣẹ rẹ náà ni: Pípé àmọ̀ọ́nnà, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{إِنَّ اللَّهَ يَأْمُرُكُمْ أَن تُؤَدُّوا الْأَمَانَاتِ إِلَىٰ أَهْلِهَا}

Dájúdájú Allāhu ń pa yín ní àṣẹ pé kí ẹ dá àgbàfipamọ́ padà fún àwọn olówó wọn An-Nisaa: 58

Nínú nnkan ti Islam pàṣẹ rẹ náà ni: Kikoraró níbi nnkan ti ko bójú mu, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«ثلاثة حق على الله عونهم: وذكر منهم: والناكح الذي يريد العفاف»

"Àwọn méta kan n bẹ, ẹtọ ni fun Ọlọhun ki O ràn wọ́n lọ́wọ́: O dárúkọ nínú wọn: Ẹni tí ó fẹ́ ṣe ìgbéyàwó ti o n gbèrò láti kóra ró níbi nnkan ti ko bójú mu" Sunanu Tirmiziy 1655 Nínú àdúrà ti Anabi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- máa n ṣe ni pe:

«اللهُمَّ إِنِّي أَسْأَلُكَ الْهُدَى وَالتُّقَى وَالْعَفَافَ وَالْغِنَى»

"Irẹ Ọlọhun, mo n tọrọ lọ́wọ́ Rẹ, imọna, ati ìpayà, àti kíkóraró níbi nnkan ti ko bójú mu, àti rírọrọ̀" Sohiihu Muslim: 2721

Nínú nnkan ti Islam n pàṣẹ rẹ náà ni ìtìjú, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«الْحَيَاءُ لَا يَأْتِي إِلَّا بِخَيْرٍ»

"Ìtìjú ko nii mu nnkan kan wá ayafi oore" Sohiihu ti Al-Bukhaar 6117 Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe:

«لِكُلِّ دِينٍ خُلُقٌ وَخُلُقُ الْإِسْلَامِ الْحَيَاءُ»

"Gbogbo ẹ̀sìn ni o ni ìwà tiẹ̀, ìwà Isilaamu náà ni ìtìjú" Al-Bayhaqiy ni o gbe e jáde nínú SHUABUL IIMAAN 6/2619

Nínú nnkan ti Islam pàṣẹ rẹ naa ni ìgboyà, láti ọ̀dọ̀ Anas- ki Ọlọhun yọ́nú si i- o sọ pe:

«كَانَ النَّبِيُّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ أَحْسَنَ النَّاسِ وَأَشْجَعَ النَّاسِ وَأَجْوَدَ النَّاسِ وَلَقَدْ فَزِعَ أَهْلُ الْمَدِينَةِ فَكَانَ النَّبِيُّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ سَبَقَهُمْ عَلَى فَرَسٍ»

"Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- jẹ ẹni tí ó dáa jù nínú àwọn ènìyàn ti o si tun gboya jù nínú àwọn ènìyàn ti o si tun n tọrẹ ju nínú àwọn ènìyàn, ẹru ba àwọn ará Mẹdina ni ọjọ́ kan ti Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- si gbawájú wọn lórí ẹṣin" Sohiihu ti Al-Bukhaar 2820 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- maa n wa ìṣọ́ra pẹ̀lú Ọlọhun kúrò níbi ojo, o maa n sọ pé:

«اللَّهُمَّ إِنِّي أَعُوذُ بِكَ مِنَ الجُبْنِ»

"Irẹ Ọlọhun, mo n sádi Ọ kúrò níbi ojo" Sohiihu ti Al-Bukhaar 6374

Nínú nnkan ti Islam n pàṣẹ rẹ náà ni ninawo àti titọrẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{مَّثَلُ الَّذِينَ يُنفِقُونَ أَمْوَالَهُمْ فِي سَبِيلِ اللَّهِ كَمَثَلِ حَبَّةٍ أَنبَتَتْ سَبْعَ سَنَابِلَ فِي كُلِّ سُنبُلَةٍ مِّائَةُ حَبَّةٍ ۗ وَاللَّهُ يُضَاعِفُ لِمَن يَشَاءُ ۗ وَاللَّهُ وَاسِعٌ عَلِيمٌ }

Àpèjúwe àwọn t'ó ń ná owó wọn fún ẹ̀sìn Allāhu dà bí àpèjúwe kóró èso kan tí ó hu ṣiri méje jáde, tí ọgọ́rùn-ún kóró sì wà lára ṣiri kọ̀ọ̀kan. Allāhu yó ṣe àdìpèlé fún ẹni tí Ó bá fẹ́. Allāhu ni Olùgbààyè, Onímọ̀. Al-Baqara 261 Ìwà Ojiṣẹ Ọlọhun- kí ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- náà ni titọrẹ, láti ọ̀dọ̀ Ibnu Abbaas- ki Ọlọhun yọnu si awọn méjèèjì- o sọ pe:

«كَانَ النَّبِيُّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ أَجْوَدَ النَّاسِ بِالخَيْرِ وَكَانَ أَجْوَدُ مَا يَكُونُ فِي رَمَضَانَ حِينَ يَلْقَاهُ جِبْرِيلُ وَكَانَ جِبْرِيلُ عَلَيْهِ السَّلاَمُ يَلْقَاهُ كُلَّ لَيْلَةٍ فِي رَمَضَانَ حَتَّى يَنْسَلِخَ يَعْرِضُ عَلَيْهِ النَّبِيُّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ القُرْآنَ فَإِذَا لَقِيَهُ جِبْرِيلُ عَلَيْهِ السَّلاَمُ كَانَ أَجْوَدَ بِالخَيْرِ مِنَ الرِّيحِ المُرْسَلَةِ»

"Anabi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni o n tọrẹ jù nínú àwọn èèyàn, igbà ti o tun maa n tọrẹ ju ni inu

Ramadan, nígbà tí Jibrīl ba wa pàdé rẹ, Jibrīl si maa n pàdé rẹ ni gbogbo òru Ramadan títí ti yóò fi tán, Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- máa n ka Kuraani fún un, ti Jibrīl ba ti wa pàdé rẹ, o jẹ ẹni tí máa n tọrẹ pẹ̀lú oore ju atẹgun ti a rán nişẹ lọ" Sohiihu ti Al-Bukhaar 1902

Nínú nnkan ti Islām n pàṣẹ rẹ naa ni ríran ẹni tí ó ní bukaata lọ́wọ́, àti ríran ẹni tí ó wa nínú ibanujẹ lọ́wọ́, àti bíbọ́ ẹni tí ebi ń pa, ati jíjẹ́ alamuleti rere, ati dida ẹbí pọ̀, ati ki káàánú àwọn ẹranko.

فعَنْ عَبْدِ اللَّهِ بْنِ عَمْرٍو رَضِيَ اللَّهُ عَنْهُمَا أَنَّ رَجُلًا سَأَلَ النَّبِيَّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ: أَيُّ الإِسْلاَمِ خَيْرٌ؟ قَالَ: «تُطْعِمُ الطَّعَامَ وَتَقْرَأُ السَّلاَمَ عَلَى مَنْ عَرَفْتَ وَمَنْ لَمْ تَعْرِفْ»

Láti ọ̀dọ̀ Abdullah ọmọ Amr- ki Ọlọhun yọ́nú si awọn méjèèjì- o wi pe arákùnrin kan bi Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- léèrè pé: "Èwo nínú Islam ni o lóore jù?", o sọ pe: "Ki o máa fún ni ni oúnjẹ jẹ, ki o si maa salamọ si ẹni ti o mọ̀ àti ẹni tí oo mọ̀". Sohiihu ti Al-Bukhaar 12 Ojişẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe:

«بَيْنَمَا رَجُلٌ يَمْشِي بِطَرِيقٍ اشْتَدَّ عَلَيْهِ العَطَشُ فَوَجَدَ بِئْرًا فَنَزَلَ فِيهَا فَشَرِبَ ثُمَّ خَرَجَ فَإِذَا كَلْبٌ يَلْهَثُ يَأْكُلُ الثَّرَى مِنَ العَطَشِ فَقَالَ الرَّجُلُ: لَقَدْ بَلَغَ هَذَا الكَلْبَ مِنَ العَطَشِ مِثْلُ الَّذِي كَانَ بَلَغَ بِي فَنَزَلَ البِئْرَ فَمَلأَ خُفَّهُ ثُمَّ أَمْسَكَهُ بِفِيهِ فَسَقَى الكَلْبَ فَشَكَرَ اللَّهُ لَهُ فَغَفَرَ لَهُ» قَالُوا: يَا رَسُولَ اللَّهِ وَإِنَّ لَنَا فِي البَهَائِمِ أَجْرًا؟ فَقَالَ: «نَعَمْ فِي كُلِّ ذَاتِ كَبِدٍ رَطْبَةٍ أَجْرٌ»

"Láàrin ìgbà tí arákùnrin kan n rìn ni ojú ọ̀nà, ni òògbẹ wa n gbẹ é gidigan, ni o wa ri kànǹga kan, ni o wa ko sínú rẹ, o si mu omi, lẹ́yìn náà ni o jáde kúrò nínú rẹ, ni o ba rí ajá kan ti o yọ ahọ́n síta ti o n jẹ erupẹ látàrí

òùngbẹ. Arákùnrin náà wa sọ pé: "Bi òùngbẹ ṣe gbẹ mi tó náà ni o ṣe gbẹ ajá yii náà, ni o ba ko sínú kannga, o wa bu omi kún inú bàtà aláwọ rẹ, o wa fi ẹnu rẹ di i mú, o si fun ajá náà ni omi mu, Ọlọhun si dupẹ fun un, O si fi orí jin in". Wọn sọ pé: "Irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, ǹjẹ́ a ó tun maa gba láádá latara àwọn ẹranko ni bí? O sọ pé:" Bẹẹni, gbogbo nnkan ti o ba ti ni ẹ̀dọ̀ tútù ni láádá bẹ nibẹ". Sọhiihu Ibnu Hibbaan 544 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«السَّاعِي عَلَى الأَرْمَلَةِ وَالمِسْكِينِ كَالْمُجَاهِدِ فِي سَبِيلِ اللَّهِ أَوِ القَائِمِ اللَّيْلَ الصَّائِمِ النَّهَارَ»

"Ẹni ti ba n ṣiṣẹ́ láti pèsè fun opó àti aláìní da gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ń jagun sí ojú ọ̀nà Ọlọhun tàbí ẹni tí ń dìde kírun ní òru tàbí ẹni tí ń gba aawẹ ni ọ̀sán" Sọhiihu ti Buhari 5353

Islam n kan iwọ̀ ẹbí nípá, o si n ṣe dída ẹbí pọ̀ ní dandan, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{النَّبِيُّ أَوْلَىٰ بِالْمُؤْمِنِينَ مِنْ أَنفُسِهِمْ ۖ وَأَزْوَاجُهُ أُمَّهَاتُهُمْ ۗ وَأُولُو الْأَرْحَامِ بَعْضُهُمْ أَوْلَىٰ بِبَعْضٍ فِي كِتَابِ اللَّهِ مِنَ الْمُؤْمِنِينَ وَالْمُهَاجِرِينَ إِلَّا أَن تَفْعَلُوا إِلَىٰ أَوْلِيَائِكُم مَّعْرُوفًا ۚ كَانَ ذَٰلِكَ فِي الْكِتَابِ مَسْطُورًا}

Ànábì ní ẹ̀tọ́ sí àwọn onígbàgbọ́ òdodo ju ẹ̀mí ara wọn lọ (nípa ìfẹ́ rẹ̀ àti ìdájọ́ rẹ̀). Àwọn aya rẹ̀ sì ni ìyá wọn. Nínú Tírà Allāhu, àwọn ẹbí, apá kan wọn ní ẹ̀tọ́ sí ogún jíjẹ ju apá kan lọ. (Àwọn ẹbí tún ní ẹ̀tọ́ sí ogún jíjẹ) ju àwọn onígbàgbọ́ òdodo àti àwọn t’ó kúrò nínú ìlú Mọkkah fún ààbò ẹ̀sìn, àfi tí ẹ bá máa ṣe dáadáa kan sí àwọn ọ̀rẹ́ yín (wọ̀nyí ni ogún lè fi kàn wọ́n pẹ̀lú àsọọ́lẹ̀). Ìyẹn wà nínú Tírà (Laohul-Mahfūṭḥ) ní àkọsílẹ̀. Al-Ah'zaab: 6 O kìlọ̀ kúrò níbi jíjá okùn ẹbí, o

si so o papọ mọ ṣíṣe ibajẹ ni orílẹ̀, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{فَهَلْ عَسَيْتُمْ إِن تَوَلَّيْتُمْ أَن تُفْسِدُوا فِي الْأَرْضِ وَتُقَطِّعُوا أَرْحَامَكُمْ (22) أُولَٰئِكَ الَّذِينَ لَعَنَهُمُ اللَّهُ فَأَصَمَّهُمْ وَأَعْمَىٰ أَبْصَارَهُمْ (23) }

Ǹjẹ́ kò súnmọ́ tí ẹ̀yin (aláìsàn ọkàn wọ̀nyí) bá dé’pò àṣẹ, pé ẹ ò níí ṣèbàjẹ́ lórí ilẹ̀ àti pé ẹ ò níí já okùn-ìbí yín?

Àwọn wọ̀nyẹn ni àwọn tí Allāhu ti ṣẹ̀bi lé. Nítorí náà, Ó di wọ́n létí pa. Ó sì fọ́ ìríran wọn. Muhammad: 22-23 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé: "Ẹni ti ba n ja okùn-ìbí ko nii wọ Alujanna". Sohiihu Muslim: 2556 Àwọn ẹbí ti o di dandan ki a so wọn pọ̀ náà ni: Àwọn òbí méjèèjì, àwọn ọmọ-ìyá lọ́kùnrin, àti àwọn ọmọ-ìyá lóbìnrin, ati awọn ọmọ-ìyá bàbá lọ́kùnrin, àti àwọn ọmọ-ìyá bàbá lóbìnrin, àti àwọn ọmọ-ìyá ìyá lọ́kùnrin, àti àwọn ọmọ-ìyá ìyá lóbìnrin.

Islam n kan iwọ̀ alamuleti nípá kódà kí ó jẹ́ Kèfèrí, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَاعْبُدُوا اللَّهَ وَلَا تُشْرِكُوا بِهِ شَيْئًا ۖ وَبِالْوَالِدَيْنِ إِحْسَانًا وَبِذِي الْقُرْبَىٰ وَالْيَتَامَىٰ وَالْمَسَاكِينِ وَالْجَارِ ذِي الْقُرْبَىٰ وَالْجَارِ الْجُنُبِ وَالصَّاحِبِ بِالْجَنبِ وَابْنِ السَّبِيلِ وَمَا مَلَكَتْ أَيْمَانُكُمْ ۗ إِنَّ اللَّهَ لَا يُحِبُّ مَن كَانَ مُخْتَالًا فَخُورًا}

Ẹ jọ́sìn fún Allāhu, ẹ má ṣe fi ǹǹkan kan ṣẹbọ sí I. Ẹ ṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì àti ẹbí àti àwọn ọmọ òrukàn àti àwọn mẹ̀kúnnù àti aládùúgbò t’ó súnmọ́ àti aládùúgbò t’ó jìnnà àti ọ̀rẹ́ alábàárìn àti ẹni tí agara dá lórí ìrìn-àjò àti àwọn ẹrú yín. Dájúdájú Allāhu kò nífẹ̀ẹ́ onígbèéraga, afọ́nnu. An-Nisaa: 36 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

(مَا زَالَ جِبْرِيلُ يُوصِينِي بِالْجَارِ حَتَّى ظَنَنْتُ أَنَّهُ سَيُوَرِّثُهُ)

(Jibrīl kò yẹ̀ kò gbò ní ẹni tí ń pa mí láṣẹ láti máa ṣe dáadáa sí aládùúgbò títí tí mo fi lérò pé yóò sọ ọ di ẹni tí yóò jogún) Sọhiihu ti Abu Daa'ud 5152

## Islam ṣe nnkan ti ó dára nínú nnkan jíjẹ ati nnkan mímu ní ẹ̀tọ́, o si tun pàṣẹ mimọ ọkàn àti ara àti ilé, torí ẹ ni o ṣe ṣe ìgbéyàwó ní ẹtọ gẹ́gẹ́ bí àwọn Anabi- ki ọlà máa bá wọn- ṣe pàṣẹ rẹ̀, gbogbo nnkan ti o dara ni wọn máa n pàṣẹ rẹ̀.

Islam ṣe nnkan ti ó dára nínú nnkan jíjẹ ati nnkan mímu ní ẹ̀tọ́, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«يَا أَيُّهَا النَّاسُ إِنَّ اللَّهَ طَيِّبٌ لَا يَقْبَلُ إِلاَّ الطَّيِّبَ وإِنَّ اللَّهَ أَمَرَ الْمُؤْمِنِينَ بِمَا أَمَرَ بِهِ الْمُرْسَلِينَ قَالَ تعالى: {يَا أَيُّهَا الرُّسُلُ كُلُوا مِنَ الطَّيِّبَاتِ وَاعْمَلُوا صَالِحًا إِنِّي بِمَا تَعْمَلُونَ عَلِيمٌ} وَقَالَ تعالى: {يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا كُلُوا مِنْ طَيِّبَاتِ مَا رَزَقْنَاكُمْ واشكروا لله إن كنتم إياه تعبدون} الآية قَالَ: ثُمَّ ذَكَرَ الرَّجُلَ يُطِيلُ السَّفَرَ أَشْعَثَ أَغْبَرَ يَمُدُّ يَدَيْهِ إِلَى السَّمَاءِ: يَا رَب يَا رَبِّ وَمَطْعَمُهُ حَرَامٌ وَمَلْبَسُهُ حَرَامٌ وَمَشْرَبُهُ حَرَامٌ وَغُذِّيَ بِالْحَرَامِ فَأَنَّى يُسْتَجَابُ لِذَلِكَ؟!»

"Mo pe ẹyin ènìyàn, dájúdájú Ọlọhun Ọba ti O dára ni, Ko si nii gba nnkan kan ayafi nnkan ti o ba dára, dájúdájú Ọlọhun pa àwọn Mumini láṣẹ pẹ̀lú nkan ti O fi pa àwọn Ojiṣẹ láṣẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:" Ẹ̀yin Òjíṣẹ́, ẹ jẹ nínú àwọn ǹǹkan dáadáa, kí ẹ sì ṣe iṣẹ́ rere. Dájúdájú Èmi ni Onímọ̀ nípa ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́". Ọlọhun ti ọla Rẹ ga tun sọ pé: "Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní

òdodo, ẹ jẹ nínú àwọn ǹǹkan dáadáa tí A pèsè fun yín, kí ẹ sì dúpẹ́ fún Allāhu tí ó bá jẹ́ pé Òun nìkan ṣoṣo ni ẹ̀ ń jọ́sìn fún". O sọ pe: Lẹ́yìn náà ni o wa dárúkọ arákùnrin náà ti o máa ṣe ìrìn-àjò gan, ti irun orí rẹ rí wúruwùru, ti ara rẹ jẹ kìkì eruku, o wa n tẹ́wọ́ rẹ méjèèjì si sanmọ pe: Irẹ Olúwa mi, Irẹ Olúwa mi, èèwọ̀ si ni nkan ti o n jẹ, eewọ ni nnkan ti o wọ̀, eewọ ni nnkan ti o n mu, wọn tún tọ ọ dàgbà pẹ̀lú nnkan eewọ, báwo ni wọn o ṣe gba adua irú ẹni bẹ́ẹ̀ Sohiihu Muslim: 1015 Allah- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{قُلْ مَنْ حَرَّمَ زِينَةَ اللَّهِ الَّتِي أَخْرَجَ لِعِبَادِهِ وَالطَّيِّبَاتِ مِنَ الرِّزْقِ ۚ قُلْ هِيَ لِلَّذِينَ آمَنُوا فِي الْحَيَاةِ الدُّنْيَا خَالِصَةً يَوْمَ الْقِيَامَةِ ۗ كَذَٰلِكَ نُفَصِّلُ الْآيَاتِ لِقَوْمٍ يَعْلَمُونَ}

Sọ pé: “Ta l’ó ṣe ọ̀ṣọ́ Allāhu, tí Ó mú jáde fún àwọn ẹrúsìn Rẹ̀ àti àwọn ǹǹkan dáadáa nínú arísìkí ní èèwọ̀?” Sọ pé: “Ó wà fún àwọn t’ó gbàgbọ́ lódodo nínú ìṣẹ̀mí ayé. Tiwọn nìkan sì ni l’Ọ́jọ́ Àjíǹde." Báyẹn ni A ṣe ń ṣàlàyé àwọn āyah fún ìjọ t’ó nímọ̀.” Al-A'roof: 32

Islam pàṣẹ mimọ ọkàn àti ara àti ilé, torí ẹ ni o ṣe ṣe ìgbéyàwó ní ẹtọ gẹ́gẹ́ bí àwọn Anabi- ki ọlà máa bá wọn- ṣe pàṣẹ rẹ̀, gbogbo nkan ti o dara ni wọn máa n pàṣẹ rẹ̀. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَاللَّهُ جَعَلَ لَكُمْ مِنْ أَنْفُسِكُمْ أَزْوَاجًا وَجَعَلَ لَكُمْ مِنْ أَزْوَاجِكُمْ بَنِينَ وَحَفَدَةً وَرَزَقَكُمْ مِنَ الطَّيِّبَاتِ أَفَبِالْبَاطِلِ يُؤْمِنُونَ وَبِنِعْمَتِ اللَّهِ هُمْ يَكْفُرُونَ}

Àti pé Allāhu ṣe àwọn ìyàwó fun yín láti ara yín. Ó fun yín ní àwọn ọmọ àti ọmọọmọ láti ara àwọn ìyàwó yín. Ó sì pèsè arísìkí fun yín nínú àwọn ǹǹkan dáadáa. Ṣé irọ́ (ìyẹn, òrìṣà) ni wọn yóò gbàgbọ́, wọn yó sì ṣài gbàgbọ́ nínú ìdẹ̀ra Allāhu? An-Nahl: 72 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{ وَثِيَابَكَ فَطَهِّرْ (4) وَالرُّجْزَ فَاهْجُرْ (5) }

Aṣọ rẹ ni kí o fọ̀ mọ́.

Òrìṣà ni kí o jìnnà sí. Al-Muddathir: 4-5 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

(لَا يَدْخُلُ الْجَنَّةَ مَنْ كَانَ فِي قَلْبِهِ مِثْقَالُ ذَرَّةٍ مِنْ كِبْرٍ. قَالَ رَجُلٌ: إِنَّ الرَّجُلَ يُحِبُّ أَنْ يَكُونَ ثَوْبُهُ حَسَنًا وَنَعْلُهُ حَسَنَةً قَالَ: إِنَّ اللهَ جَمِيلٌ يُحِبُّ الْجَمَالَ الْكِبْرُ بَطَرُ الْحَقِّ وَغَمْطُ النَّاسِ)

(Ẹni tí odiwọn ọmọ iná-igún nínú ìgbéraga ba n bẹ nínú ọkàn rẹ ko nii wọ Alijanna. Arákùnrin kan sọ pé: Èèyàn ti o ba wa nífẹ̀ẹ́ sí ki aṣọ rẹ dáa àti ki bàtà rẹ dáa ńkọ́. O sọ pe: Ọlọhun Ọba ti O rẹwà ni, O si nífẹ̀ẹ́ si ẹwà, ìgbéraga ni kíkọ òdodo àti yiyẹpẹrẹ àwọn ènìyàn) Sohiihu Muslim: 91

**Islām ṣe àwọn ipilẹ àwọn nkan ti a ṣe ni eewọ ni eewọ, gẹgẹ bii ẹbọ pẹ̀lú Ọlọhun, àti ṣíṣe Kèfèrí, ati sísin àwọn ooṣa, ati sisọ ohun ti èèyàn ò mọ̀ nípa Ọlọhun, àti pípa àwọn ọmọ, ati pípa ẹ̀mí ti a pọnle, àti ṣíṣe ibajẹ ni orílẹ̀, àti idán, ati ìwà ibajẹ ti o fi ojú hàn ati èyí tí ó pamọ, àti ṣìná, ati ki ọkùnrin maa ba ọkùnrin ẹgbẹ́ rẹ ni aṣepọ, o ṣe èlé ni eewọ àti jíjẹ okunbete, àti àwọn nkan ti wọn ba dú fún àwọn ooṣa, o ṣe ẹran ẹlẹ́dẹ̀ ni eewọ, àti àwọn ẹgbin ti o**

**ṣẹ́kù, o ṣe jíjẹ dúkìá ọmọ orukan ni eewọ, ati didin òṣùwọ̀n kù, o ṣe jija okùn-ìbí ni eewọ. Àwọn Anọbi pátá- ki ọlà maa ba wọn- ni wọn fi ẹnu ko lori ṣíṣe àwọn nkan eewọ yii ni eewọ.**

Islām ṣe àwọn ipilẹ àwọn nnkan ti a ṣe ni eewọ ni eewọ, gẹgẹ bii ẹbọ pẹ̀lú Ọlọhun, àti ṣíṣe kèfèrí, ati sísin àwọn ooṣa, ati sisọ ohun ti èèyàn ò mọ̀ nípa Ọlọhun, àti pípa àwọn ọmọ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{قُلۡ تَعَالَوۡاْ أَتۡلُ مَا حَرَّمَ رَبُّكُمۡ عَلَيۡكُمۡۖ أَلَّا تُشۡرِكُواْ بِهِۦ شَيۡـٔٗاۖ وَبِٱلۡوَٰلِدَيۡنِ إِحۡسَٰنٗاۖ وَلَا تَقۡتُلُوٓاْ أَوۡلَٰدَكُم مِّنۡ إِمۡلَٰقٖ نَّحۡنُ نَرۡزُقُكُمۡ وَإِيَّاهُمۡۖ وَلَا تَقۡرَبُواْ ٱلۡفَوَٰحِشَ مَا ظَهَرَ مِنۡهَا وَمَا بَطَنَۖ وَلَا تَقۡتُلُواْ ٱلنَّفۡسَ ٱلَّتِي حَرَّمَ ٱللَّهُ إِلَّا بِٱلۡحَقِّۚ ذَٰلِكُمۡ وَصَّىٰكُم بِهِۦ لَعَلَّكُمۡ تَعۡقِلُونَ وَلَا تَقۡرَبُواْ مَالَ ٱلۡيَتِيمِ إِلَّا بِٱلَّتِي هِيَ أَحۡسَنُ حَتَّىٰ يَبۡلُغَ أَشُدَّهُۥۚ وَأَوۡفُواْ ٱلۡكَيۡلَ وَٱلۡمِيزَانَ بِٱلۡقِسۡطِۖ لَا نُكَلِّفُ نَفۡسًا إِلَّا وُسۡعَهَاۖ وَإِذَا قُلۡتُمۡ فَٱعۡدِلُواْ وَلَوۡ كَانَ ذَا قُرۡبَىٰۖ وَبِعَهۡدِ ٱللَّهِ أَوۡفُواْۚ ذَٰلِكُمۡ وَصَّىٰكُم بِهِۦ لَعَلَّكُمۡ تَذَكَّرُونَ}

Sọ pé: "Ẹ wá kí n̄g ka ohun tí Olúwa yín ṣe ní èèwọ̀ fun yín; pé kí ẹ má ṣe fi n̄ǹkan kan ṣẹbọ sí I, (kí ẹ sì ṣe) dáadáa sí àwọn òbí (yín) méjèèjì, kí ẹ sì má ṣe pa àwọn ọmọ yín nítorí (ìbẹ̀rù) òṣì, – Àwa ni À ń pèsè fun ẹyin àti àwọn – kí ẹ sì má ṣe súnmọ́ àwọn ìwà ìbájẹ́ – èyí t'ó hàn nínú rẹ̀ àti èyí t'ó pamọ́, - àti pé kí ẹ sì má ṣe pa ẹ̀mí (ènìyàn) tí Allāhu ṣe ní èèwọ̀ àyàfi ní ọ̀nà ẹ̀tọ́. Ìyẹn l'Ó pa láṣẹ fun yín nítorí kí ẹ lè ṣe làákàyè.

Ẹ má ṣe súnmọ́ dúkìá ọmọ òrukàn àyàfi ní ọ̀nà t'ó dára jùlọ títí ó fi máa dàgbà. Ẹ wọn kóńgò àti òṣùwọ̀n pé dáadáa. A kò làbọ ẹ̀mí kan lọ́rùn àyàfi ìwọ̀n agbára rẹ̀. Tí ẹ bá sọ̀rọ̀, ẹ ṣe déédé, ìbáà jẹ́ ìbátan. Kí ẹ sì pé àdéhùn Allāhu. Ìyẹn l'Ó pa láṣẹ fun yín nítorí kí ẹ lè lo

ìrántí. Al-An'aam 151-152 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{قُلْ إِنَّمَا حَرَّمَ رَبِّيَ الْفَوَاحِشَ مَا ظَهَرَ مِنْهَا وَمَا بَطَنَ وَالْإِثْمَ وَالْبَغْيَ بِغَيْرِ الْحَقِّ وَأَن تُشْرِكُوا بِاللَّهِ مَا لَمْ يُنَزِّلْ بِهِ سُلْطَانًا وَأَن تَقُولُوا عَلَى اللَّهِ مَا لَا تَعْلَمُونَ}

Sọ pé: "Ohun tí Olúwa mi ṣe ní èèwọ̀ ni àwọn ìwà ìbàjẹ́ – èyí t'ó fojú hàn nínú rẹ̀ àti èyí t'ó pamọ́ –, ìwà ẹ̀ṣẹ̀, ọ̀tẹ̀ ṣíṣe láì lẹ́tọ̀ọ́, bíbá Allāhu wá akẹgbẹ́ – èyí tí kò sọ ẹ̀rí kan kalẹ̀ fún – àti ṣíṣe àfitì ohun tí ẹ ò nímọ̀ nípa rẹ̀ sọ́dọ̀ Allāhu." Al-A'roof: 33

Islam ṣe pípa ẹ̀mí ti a pọ́nlé ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَلَا تَقۡتُلُواْ ٱلنَّفۡسَ ٱلَّتِي حَرَّمَ ٱللَّهُ إِلَّا بِٱلۡحَقِّۗ وَمَن قُتِلَ مَظۡلُومٗا فَقَدۡ جَعَلۡنَا لِوَلِيِّهِۦ سُلۡطَٰنٗا فَلَا يُسۡرِف فِّي ٱلۡقَتۡلِۖ إِنَّهُۥ كَانَ مَنصُورٗا}

Ẹ má pa ẹ̀mí tí Allāhu ṣe (pípa rẹ̀) ní èèwọ̀ àyàfi ní ọ̀nà ẹ̀tọ́. Ẹni tí wọ́n bá pa ní ìpa àbòsí, dájúdájú A ti fún alámòjúútó rẹ̀ ní agbára (láti gbẹ̀san). Nítorí náà, kí ẹnikẹ́ni má ṣe tayọ ẹnu- àlà níbi ìpànìyàn (nítorí pé) dájúdájú A máa ran (ẹbí òkú) lọ́wọ́ (láti gbẹ̀san). Al-Isroo: 33 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{وَالَّذِينَ لَا يَدْعُونَ مَعَ اللَّهِ إِلَٰهًا آخَرَ وَلَا يَقْتُلُونَ النَّفْسَ الَّتِي حَرَّمَ اللَّهُ إِلَّا بِالْحَقِّ وَلَا يَزْنُونَ ۚ وَمَن يَفْعَلْ ذَٰلِكَ يَلْقَ أَثَامًا }

(Àwọn ni) àwọn tí kò pe ọlọ́hun mìíràn mọ́ Allāhu. Wọn kò pa ẹ̀mí tí Allāhu ṣe (pípa rẹ̀) ní èèwọ̀ àfi ní ọ̀nà ẹ̀tọ́. Àti pé wọn kò ṣe zinā. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe (aburú) yẹn, ó máa pàdé (ìyà) ẹ̀ṣẹ̀. Al-Furqaan: 68

Islam ṣe ibajẹ lórí ilẹ̀ ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَلَا تُفْسِدُوا فِي الْأَرْضِ بَعْدَ إِصْلَاحِهَا}

Ẹ sì má ṣe ìbàjẹ́ lórí ilẹ̀ lẹ́yìn àtúnṣe rẹ̀. Al-A'rọọf 56

وقال الله تعالى مخبراً عن النبي شعيب عليه السلام أن قال لقومه: {يَا قَوْمِ اعْبُدُوا اللَّهَ مَا لَكُم مِّنْ إِلَٰهٍ غَيْرُهُ ۖ قَدْ جَاءَتْكُم بَيِّنَةٌ مِّن رَّبِّكُمْ ۖ فَأَوْفُوا الْكَيْلَ وَالْمِيزَانَ وَلَا تَبْخَسُوا النَّاسَ أَشْيَاءَهُمْ وَلَا تُفْسِدُوا فِي الْأَرْضِ بَعْدَ إِصْلَاحِهَا ۚ ذَٰلِكُمْ خَيْرٌ لَّكُمْ إِن كُنتُم مُّؤْمِنِينَ}

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ nípa Anọbi Shuaib- ki ọlà Ọlọhun maa ba a- wípé o sọ fún àwọn ìjọ rẹ̀ pé:

"Ẹ̀yin ìjọ mi, ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Ẹ è ní ọlọ́hun mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀. Dájúdájú ẹ̀rí t'ó yanjú ti dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín. Nítorí náà, ẹ wọn kóńgò àti òṣùwọ̀n kún. Ẹ má ṣe dín ǹǹkan àwọn èniyàn kù. Ẹ sì má ṣe ìbàjẹ́ lórí ilẹ̀ lẹ́yìn àtúnṣe rẹ̀. Ìyẹn sì lóore jùlọ fun yín tí ẹ bá jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo. Suratul A'raf: 85

Islam ṣe idán ni eewọ, Ọba Òdodo- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَأَلْقِ مَا فِي يَمِينِكَ تَلْقَفْ مَا صَنَعُوٓا۟ ۖ إِنَّمَا صَنَعُوا۟ كَيْدُ سَٰحِرٍ ۖ وَلَا يُفْلِحُ ٱلسَّاحِرُ حَيْثُ أَتَىٰ}

Ju ohun tí ń bẹ ní ọwọ́ ọ̀tún rẹ sílẹ̀. Ó sì máa gbé ohun tí wọ́n ṣe kalẹ̀ mì káló. Dájúdájú ohun tí wọ́n ṣe kalẹ̀, ète òpìdán ni. Òpìdán kò sì níí jèrè ní ibikíbi tí ó bá dé." TOO'HAA 69 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«اجْتَنِبُوا السَّبْعَ المُوبِقَاتِ قَالُوا: يَا رَسُولَ اللَّهِ وَمَا هُنَّ؟ قَالَ: الشِّرْكُ بِاللَّهِ وَالسِّحْرُ وَقَتْلُ النَّفْسِ الَّتِي حَرَّمَ اللَّهُ إِلَّا بِالحَقِّ وَأَكْلُ الرِّبَا وَأَكْلُ مَالِ اليَتِيمِ وَالتَّوَلِّي يَوْمَ الزَّحْفِ وَقَذْفُ المُحْصَنَاتِ المُؤْمِنَاتِ الغَافِلاَتِ»

"Ẹ jìnà sí nkan méje ti o maa n fa ìparun, wọn sọ pé: Irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, kini àwọn nkan naa? O sọ pe: Iwa orogun pẹ̀lú Ọlọhun, ati idán, ati pípa ẹ̀mí ti Ọlọhun ṣe

ni eewọ afi pẹ̀lú ẹtọ, ati jíjẹ riba, ati jíjẹ dúkìá ọmọ orukan, ati sisalọ fun ogun jíjà, ati pípa irọ́ ṣina mọ àwọn ọmọ̀luabi l'obinrin, àwọn ti wọn gbagbọ l'ododo, àwọn ti sina ko si lórí ọkàn wọn Sohiihu ti Al-Bukhaar 6857

Islam ṣe ìwà ìbàjẹ́ ti o hàn àti èyí tí o pamọ ni eewọ, ati sina, ati ki ọkùnrin méjì maa ba ara wọn ṣe lọkọ-laya, a si ti sọ síwájú ni ìbẹ̀rẹ̀ ipinrọ yii àwọn aaya ti o tọka si ìyẹn, Islām si ṣe riba ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا اتَّقُوا اللَّهَ وَذَرُوا مَا بَقِيَ مِنَ الرِّبَا إِن كُنتُم مُّؤْمِنِينَ (278) فَإِن لَّمْ تَفْعَلُوا فَأْذَنُوا بِحَرْبٍ مِّنَ اللَّهِ وَرَسُولِهِ ۖ وَإِن تُبْتُمْ فَلَكُمْ رُءُوسُ أَمْوَالِكُمْ لَا تَظْلِمُونَ وَلَا تُظْلَمُونَ (279)}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ bẹ̀rù Allāhu, kí ẹ sì fi ohun t’ó ṣẹ́kù nínú èlé sílẹ̀, tí ẹ bá jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo.

Tí ẹ ò bá ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ lọ mọ̀ pé ogun kan láti ọ̀dọ̀ Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀ (ń bọ̀ wá ba yín). Tí ẹ bá sì ronú pìwàdà, tiyín ni ojú-owó yín. Ẹ ò níí ṣàbòsí (sí wọn). Wọn kò sì níí ṣàbòsí si yín. Al-Baqara 278-279 Ọlọhun ko ṣe ìlérí ìyà pẹ̀lú ogun fun ẹlẹṣẹ kankan gẹ́gẹ́ bí O ṣe ṣe e fún ẹni tí o n gba èlé; toripe o n bẹ nibi èlé iba ẹ̀sìn jẹ, ati ìlú, ati dúkìá, ati ẹ̀mí.

Islam ṣe jíjẹ okunbete ni eewọ, ati nnkan ti wọn ba du fun ooṣa, o si ṣe ẹran ẹlẹdẹ ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{حُرِّمَتْ عَلَيْكُمُ الْمَيْتَةُ وَالدَّمُ وَلَحْمُ الْخِنزِيرِ وَمَا أُهِلَّ لِغَيْرِ اللَّهِ بِهِ وَالْمُنْخَنِقَةُ وَالْمَوْقُوذَةُ وَالْمُتَرَدِّيَةُ وَالنَّطِيحَةُ وَمَا أَكَلَ السَّبُعُ إِلَّا مَا ذَكَّيْتُمْ وَمَا ذُبِحَ عَلَى النُّصُبِ وَأَن تَسْتَقْسِمُوا بِالْأَزْلَامِ ۚ ذَٰلِكُمْ فِسْقٌ}

A ṣe é ní èèwọ̀ fun yín ẹran òkúǹbete, àti ẹ̀jẹ̀, àti ẹran ẹlẹ́dẹ̀, àti èyí tí wọ́n pa pẹ̀lú orúkọ tí kì í ṣe Allāhu, àti ẹran tí wọ́n fún lọ́rùn pa, àti ẹran tí wọ́n lù pa, àti ẹran tí ó ré lulẹ̀ kú, àti ẹran tí wọ́n kàn pa àti èyí tí ẹranko abìjàwàrà jẹ kù àfi èyí tí ẹ bá rí dú (ṣíwájú kí ó tó kú) àti èyí tí wọ́n pa sídìí òrìṣà. Èèwọ̀ sì ni fun yín láti yẹṣẹ́ wò. Ìwọ̀nyí ni ìbàjẹ́ (Al'Maa'idah 3)

Islam ṣe mímu ọtí ni eewọ ati awọn nnkan ẹgbin to ku, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا إِنَّمَا الْخَمْرُ وَالْمَيْسِرُ وَالْأَنصَابُ وَالْأَزْلَامُ رِجْسٌ مِّنْ عَمَلِ الشَّيْطَانِ فَاجْتَنِبُوهُ لَعَلَّكُمْ تُفْلِحُونَ (90) إِنَّمَا يُرِيدُ الشَّيْطَانُ أَن يُوقِعَ بَيْنَكُمُ الْعَدَاوَةَ وَالْبَغْضَاءَ فِي الْخَمْرِ وَالْمَيْسِرِ وَيَصُدَّكُمْ عَن ذِكْرِ اللَّهِ وَعَنِ الصَّلَاةِ ۖ فَهَلْ أَنتُم مُّنتَهُونَ (91)}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, dájúdájú ọtí, tẹ́tẹ́, àwọn òrìṣà àti iṣẹ́ yíyẹ̀wò, ẹ̀gbin nínú iṣẹ́ Èṣù ni. Nítorí náà, ẹ jìnnà sí i nítorí kí ẹ lè jèrè.

Ohun tí Èṣù ń fẹ́ ni pé ó máa dá ọ̀tá àti ìkórira sílẹ̀ láààrin yín níbi ọtí àti tẹ́tẹ́. Ó sì fẹ́ ṣẹ yín lórí kúrò níbi ìrántí Allāhu àti níbi ìrun kíkí. Ṣé ẹ̀yin kò níí jáwọ́ (níbi iṣẹ́ Èṣù) ni? Al-Maa'ida 90-91 A ti sọ síwájú ninu ipinrọ ti nọ́mbà rẹ̀ jẹ́ (31) wípé Ọlọhun sọ pe lara àwọn ìròyìn Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ninu Taoreeta ni pe yóò ṣe àwọn nkan àìdáa ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ الَّذِينَ يَتَّبِعُونَ الرَّسُولَ النَّبِيَّ الْأُمِّيَّ الَّذِي يَجِدُونَهُ مَكْتُوبًا عِندَهُمْ فِي التَّوْرَاةِ وَالْإِنجِيلِ يَأْمُرُهُم بِالْمَعْرُوفِ وَيَنْهَاهُمْ عَنِ الْمُنكَرِ وَيُحِلُّ لَهُمُ الطَّيِّبَاتِ وَيُحَرِّمُ عَلَيْهِمُ الْخَبَائِثَ وَيَضَعُ عَنْهُمْ إِصْرَهُمْ وَالْأَغْلَالَ الَّتِي كَانَتْ عَلَيْهِمْ ۚ}

Àwọn t'ó ń tẹ̀lé Òjíṣẹ́ náà, Ànábì aláìmọ̀ọ́nkọmọ̀ọ́nkà, ẹni tí wọ́n yóò bá àkọsílẹ̀ nípa rẹ̀

lọ́dọ̀ wọn nínú at-Taorāh àti al-’Injīl, tí ó ń pa wọ́n láṣẹ ohun rere, tí ó ń kọ ohun burúkú fún wọn, tí ó ń ṣe àwọn ǹǹkan dáadáa lẹ́tọ̀ọ́ fún wọn, tí ó sì ń ṣe àwọn ǹǹkan àìdáa léèwọ̀ fún wọn, tí ó tún máa gbé ẹrù (àdéhùn t’ó wúwo) àti àjàgà t’ó ń bẹ lọ́rùn wọn kúrò fún wọn Al-A'rọọf 157

Islam ṣe jíjẹ dúkìá ọmọ orukan ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَآتُوا الْيَتَامَىٰ أَمْوَالَهُمْ ۖ وَلَا تَتَبَدَّلُوا الْخَبِيثَ بِالطَّيِّبِ ۖ وَلَا تَأْكُلُوا أَمْوَالَهُمْ إِلَىٰ أَمْوَالِكُمْ ۚ إِنَّهُ كَانَ حُوبًا كَبِيرًا}

Ẹ fún àwọn ọmọ òrukàn ní dúkìá wọn. Ẹ má ṣe fi ǹǹkan burúkú pààrọ̀ ǹǹkan dáadáa. Ẹ sì má ṣe jẹ dúkìá wọn mọ́ dúkìá yín; dájúdájú ó jẹ́ ẹ̀ṣẹ̀ ńlá. An-Nisaa 2

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{إِنَّ الَّذِينَ يَأْكُلُونَ أَمْوَالَ الْيَتَامَىٰ ظُلْمًا إِنَّمَا يَأْكُلُونَ فِي بُطُونِهِمْ نَارًا ۖ وَسَيَصْلَوْنَ سَعِيرًا}

Dájúdájú àwọn t’ó ń jẹ dúkìá ọmọ òrukàn pẹ̀lú àbòsí, Iná kúkú ni wọ́n ń jẹ sínú ikùn wọn. Wọ́n sì máa wọ inú Iná t’ó ń jò. An-Nisaa 10

Islam ṣe didin òṣùwọ̀n ku ni eewọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَيْلٌ لِّلْمُطَفِّفِينَ (1) الَّذِينَ إِذَا اكْتَالُوا عَلَى النَّاسِ يَسْتَوْفُونَ (2) وَإِذَا كَالُوهُمْ أَو وَّزَنُوهُمْ يُخْسِرُونَ (3) أَلَا يَظُنُّ أُولَٰئِكَ أَنَّهُم مَّبْعُوثُونَ (4)}

Ègbé ni fún àwọn olùdín-òṣùwọ̀n-kù

àwọn (òǹtajà) t’ó jẹ́ pé nígbà tí wọ́n bá wọn ǹǹkan lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn, wọ́n á gbà á ní ẹ̀kún,

nígbà tí àwọn (òǹtajà náà) bá sì lo ìwọ̀n fún àwọn (òǹrajà) tàbí lo òṣùwọ̀n fún wọn, wọn yóò dín in kù.

Ṣé àwọn wọ̀nyẹn kò mọ̀ dájú pé dájúdájú A máa gbé wọn dìde Al-Mutaffifiin 1-4

Islām ṣe jija okun ẹbí ni eewọ, a ti sọ síwájú nínú ipinrọ tí nọ́mbà rẹ̀ jẹ́ (31) àwọn aaya ati hadiisi to n tọ́ka si ìyẹn, àwọn Anọbi ati awọn Ojiṣẹ pátápátá- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn- ni wọ́n fi ẹnu ko lori ṣiṣe àwọn nnkan eewọ yii ni eewọ

## Islām n kọ àwọn ìwà burúkú bii irọ́, irẹjẹ, ìjànbá, ẹtanjẹ, keeta, ète aburú, olè-jíjà, tẹnbẹlẹkun, ati àbòsí, Islam kọ gbogbo ìwà ti ko dára.

Islam n kọ àwọn ìwà burúkú ni àpapọ̀, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَلَا تُصَعِّرْ خَدَّكَ لِلنَّاسِ وَلَا تَمْشِ فِي ٱلْأَرْضِ مَرَحًاۖ إِنَّ ٱللَّهَ لَا يُحِبُّ كُلَّ مُخْتَالٍ فَخُورٍ}

Má ṣe kọ párìkẹ́ rẹ sí ènìyàn. Má sì ṣe rìn lórí ilẹ̀ pẹ̀lú fáàrí. Dájúdájú Allāhu kò fẹ́ràn gbogbo onígbèéraga, onífáàrí. Luqman 18 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

« إنَّ من أحبِّكم إليَّ وأقربكم منِّي مجلسًا يومَ القيامةِ أحاسنَكُم أخلاقًا وإنَّ أبغضَكم إليَّ وأبعدَكم منِّي مجلسًا يومَ القيامةِ الثَّرثارونَ والمتشدِّقونَ والمتفَيهِقون قالوا يا رسولَ اللَّهِ قد علِمنا الثَّرثارونَ والمتشدِّقونَ فما المتفَيهِقونَ قالَ المتكبِّرونَ »

Dájúdájú nínú àwọn ti mo nífẹ̀ẹ́ si ju nínú yín, ti ibùjókòó wọn yoo si sunmọ mi ju ni ọjọ igbende, àwọn naa ni àwọn ti ìwà wọn dára jù nínú yin, àwọn ti mo sì korira ju nínú yín, ti ibùjókòó wọn yóò si jìnà si mi ju ni ọjọ́ igbende, àwọn naa ni àwọn ẹlẹjọ-wẹwẹ, ati awọn

alasọtan-ọrọ, ati awọn al-mutafay'hiquun, wọn sọ pé: Irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, a ti mọ àwọn ẹlẹjọ-wẹwẹ ati awọn alasọtan-ọrọ, àwọn wo wa ni al-mutafay'hiquun? O sọ pe: Àwọn naa ni àwọn onigberaga. As-Silsilatu As-Sohiiha 791

Islam kọ irọ́ pípa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{ إِنَّ ٱللَّهَ لَا يَهۡدِي مَنۡ هُوَ مُسۡرِفٞ كَذَّابٞ}

Dájúdájú Allāhu kò níí fi ọ̀nà mọ ẹni tí ó jẹ́ aláṣejù, òpùrọ́. Gaafir 28 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba - sọ pe:

«وَإِيَّاكُمْ وَالْكَذِبَ فَإِنَّ الْكَذِبَ يَهْدِي إِلَى الْفُجُورِ وَإِنَّ الْفُجُورَ يَهْدِي إِلَى النَّارِ وَمَا يَزَالُ الرَّجُلُ يَكْذِبُ وَيَتَحَرَّى الْكَذِبَ حَتَّى يُكْتَبَ عِنْدَ اللهِ كَذَّابًا»

Ẹ ṣọ́ra fun irọ́ pípa, torí pé irọ maa n sun ni lọ sibi ẹ̀ṣẹ̀ ni, ẹ̀ṣẹ̀ si nìyí, o maa n sun ni lọ inú iná ni, ọmọniyan ko nii yẹ ko nii gbo lẹniti yoo maa pa irọ́, ti yoo tun maa wa gbogbo ọna láti pa irọ́, títí wọn yóò fi kọ ọ ni ọdọ Ọlọhun pé opurọ ni. Sohiihu Muslim: 2607 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«آيَةُ المُنَافِقِ ثَلاَثٌ: إِذَا حَدَّثَ كَذَبَ وَإِذَا وَعَدَ أَخْلَفَ وَإِذَا اؤْتُمِنَ خَانَ»

Àmì ti a fi n da munafiki mọ mẹta ni: Ti o ba sọrọ yóò parọ, ti o ba ṣe àdéhùn yóò yapa, ti wọn ba gbára le e yóò janba Sọhiihu ti Buhari 6095

Islām kọ irẹjẹ

وجاء في الحديث أن رَسُولَ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ مَرَّ عَلَى صُبْرَةِ طَعَامٍ فَأَدْخَلَ يَدَهُ فِيهَا فَنَالَتْ أَصَابِعُهُ بَلَلًا فَقَالَ: «مَا هَذَا يَا صَاحِبَ الطَّعَامِ؟» قَالَ أَصَابَتْهُ السَّمَاءُ يَا رَسُولَ اللهِ قَالَ: أَفَلَا جَعَلْتَهُ فَوْقَ الطَّعَامِ كَيْ يَرَاهُ النَّاسُ مَنْ غَشَّ فَلَيْسَ مِنِّي»

O wa ninu Hadiisi pe Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- kọjá níbi tí òkìtì oúnjẹ kan wa, o wa

ki ọwọ́ rẹ bọ inú oúnjẹ naa, ni ọwọ́ rẹ̀ wa tutù, o wa sọ pé: Kini eléyìí, irẹ oluta-ounjẹ? O sọ pe: Òjó ni o pa a irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, o sọ pe: I ba dára ki o jẹ ki èyí ti ojo pa yìí wa lókè ki awọn èèyàn lè ri i, ẹnikẹ́ni ti o ba ti wuwa irẹjẹ ki i ṣe ara ìjọ mi. Sohiihu Muslim: 102

Islam kọ ìjàmbá àti ẹtanjẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا لَا تَخُونُوا اللَّهَ وَالرَّسُولَ وَتَخُونُوا أَمَانَاتِكُمْ وَأَنتُمْ تَعْلَمُونَ }

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ má ṣe jàǹbá (ọ̀ran-anyàn) Allāhu àti (sunnah) Òjíṣẹ́; ẹ má ṣe jàǹbá àwọn àgbàfipamọ́ yín, ẹ sì mọ (ìjàǹbá). Al-Anfaal 27 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- tun sọ pe:

{ ٱلَّذِينَ يُوفُونَ بِعَهۡدِ ٱللَّهِ وَلَا يَنقُضُونَ ٱلۡمِيثَٰقَ}

(Àwọn ni) àwọn t'ó ń mú àdéhùn Allāhu ṣẹ. Àti pé wọn kì í tú àdéhùn. Ar-Ra'd 20 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- máa n sọ fún àwọn ọmọ ogun rẹ ti wọn ba jáde pe:

«اغْزُوا وَلَا تَغُلُّوا وَلَا تَغْدِرُوا وَلَا تَمْثُلُوا وَلَا تَقْتُلُوا وَلِيدًا»

Ẹ lọ jagun, ẹ o gbọdọ ji mu nínú ọrọ̀ ogun síwájú ki wọn o tó pin in, ẹ o gbọ́dọ̀ jàǹbá àdéhùn, ẹ o gbọ́dọ̀ ṣe ẹni tí ẹ bá pa ni ìṣekúṣe, ẹ o gbọ́dọ̀ pa ọmọ ti ko bai tii bàlágà. Sọhiihu ti Muslim 1731 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«أَرْبَعٌ مَنْ كُنَّ فِيهِ كَانَ مُنَافِقًا خَالِصًا وَمَنْ كَانَتْ فِيهِ خَصْلَةٌ مِنْهُنَّ كَانَتْ فِيهِ خَصْلَةٌ مِنَ النِّفَاقِ حَتَّى يَدَعَهَا: إِذَا اؤْتُمِنَ خَانَ وَإِذَا حَدَّثَ كَذَبَ وَإِذَا عَاهَدَ غَدَرَ وَإِذَا خَاصَمَ فَجَرَ»

Nnkan mẹẹrin kan n bẹ, ẹni tí wọn ba ti wà lára rẹ̀, o ti di munafiki pọnnbele, ẹni ti ìròyìn kan nínú ẹ ba ti

wa lára rẹ, o ti ni ìròyìn nínú ìwà munafiki lára nìyẹn títí yóò fi fi í sílẹ̀: Ti wọn ba fi ọkàn tan an yóò jàǹbá, ti o ba sọrọ yoo parọ, ti o ba ṣe àdéhùn yóò yapa, ti o ba ba èèyàn ja yóò pa irọ́ Sohiihu ti Al-Bukhaar 34

Islam kọ keeta, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{أَمْ يَحْسُدُونَ النَّاسَ عَلَىٰ مَا آتَاهُمُ اللَّهُ مِن فَضْلِهِ ۖ فَقَدْ آتَيْنَا آلَ إِبْرَاهِيمَ الْكِتَابَ وَالْحِكْمَةَ وَآتَيْنَاهُم مُّلْكًا عَظِيمًا}

Tàbí wọ́n ń ṣe ìlara àwọn ènìyàn lórí ohun tí Allāhu fún wọn nínú oore àjùlọ Rẹ̀ ni? Dájúdájú A fún àwọn ẹbí (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm ní Tírà àti ìjìnlẹ̀ òye (sunnah). A sì fún wọn ní ìjọba t’ó tóbi. An-Nisaa 54 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{وَدَّ كَثِيرٌ مِّنْ أَهْلِ الْكِتَابِ لَوْ يَرُدُّونَكُم مِّن بَعْدِ إِيمَانِكُمْ كُفَّارًا حَسَدًا مِّنْ عِندِ أَنفُسِهِم مِّن بَعْدِ مَا تَبَيَّنَ لَهُمُ الْحَقُّ ۖ فَاعْفُوا وَاصْفَحُوا حَتَّىٰ يَأْتِيَ اللَّهُ بِأَمْرِهِ ۗ إِنَّ اللَّهَ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ قَدِيرٌ}

Ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ nínú àwọn tí A fún ní Tírà ń fẹ́ láti da yín padà sípò kèfèrí lẹ́yìn tí ẹ ti ní ìgbàgbọ́ òdodo, ní ti kèéta láti inú ẹ̀mí wọn, (àti) lẹ́yìn tí òdodo (’Islām) ti fojú hàn sí wọn. Nítorí náà, ẹ foríjìn wọ́n, kí ẹ ṣàmójú kúrò fún wọn (nípa ìnira tí wọ́n ń fi kàn yín) títí Allāhu yó fi mú àṣẹ Rẹ̀ wá (láti ja wọ́n lógun). Dájúdájú Allāhu ni Alágbára lórí gbogbo ǹǹkan. Al-Baqara 109 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«دَبَّ إِلَيْكُمْ دَاءُ الأُمَمِ قَبْلَكُمْ: الحَسَدُ وَالبَغْضَاءُ هِيَ الحَالِقَةُ لَا أَقُولُ تَحْلِقُ الشَّعَرَ وَلَكِنْ تَحْلِقُ الدِّينَ وَالَّذِي نَفْسِي بِيَدِهِ لَا تَدْخُلُوا الجَنَّةَ حَتَّى تُؤْمِنُوا وَلَا تُؤْمِنُوا حَتَّى تَحَابُّوا أَفَلَا أُنَبِّئُكُمْ بِمَا يُثَبِّتُ ذَلِكَ لَكُمْ؟ أَفْشُوا السَّلَامَ بَيْنَكُمْ»

Àrùn àwọn ìjọ ti wọn ṣíwájú yín ti rìn wọ ààrin yín: Ìlara ati ikorira, oun naa si ni olufa-nkan, mi o sọ pe o maa fa orí o, ṣùgbọ́n ẹsin ni o maa fa, mo fi Ẹni ti ẹ̀mí

mi n bẹ lọ́wọ́ Rẹ̀ búra, ẹ o le wọ alujanna titi ti ẹ maa fi ni ìgbàgbọ́, ẹ o si nii gbagbọ títí ti ẹ o fi nífẹ̀ẹ́ ara yín, ṣe ki n fun yin ni iro nípa nkan ti yóò fi ìyẹn rinlẹ̀ fun yin? Ẹ maa fọn salamọ ka láàrin yin. Sunanu Tirmiziy 2510

Islam kọ ète aburu, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَكَذَٰلِكَ جَعَلْنَا فِي كُلِّ قَرْيَةٍ أَكَابِرَ مُجْرِمِيهَا لِيَمْكُرُوا فِيهَا ۖ وَمَا يَمْكُرُونَ إِلَّا بِأَنفُسِهِمْ وَمَا يَشْعُرُونَ}

Báyẹn ni A ṣe sọ àwọn àgbà kan di ọ̀daràn ìlú nínú ìlú kọ̀ọ̀kan, nítorí kí wọ́n lè máa dète níbẹ̀. Wọn kò sì dète sí ẹnikẹ́ni bí kò ṣe sí ara wọn, wọn kò sì fura. An-Aam 123 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe àwọn yẹhudi gbìyànjú láti pa Anọbi Isa- ki ọlà Ọlọhun maa ba a- wọn da ète, Ọlọhun naa si da ète si wọn, Ọlọhun wa ṣe àlàyé pé iya ète aburú ko nii ko le ẹni kan lórí afi oniṣẹ aburu, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{فَلَمَّا أَحَسَّ عِيسَىٰ مِنْهُمُ الْكُفْرَ قَالَ مَنْ أَنصَارِي إِلَى اللَّهِ ۖ قَالَ الْحَوَارِيُّونَ نَحْنُ أَنصَارُ اللَّهِ آمَنَّا بِاللَّهِ وَاشْهَدْ بِأَنَّا مُسْلِمُونَ (52) رَبَّنَا آمَنَّا بِمَا أَنزَلْتَ وَاتَّبَعْنَا الرَّسُولَ فَاكْتُبْنَا مَعَ الشَّاهِدِينَ (53) وَمَكَرُوا وَمَكَرَ اللَّهُ ۖ وَاللَّهُ خَيْرُ الْمَاكِرِينَ (54) إِذْ قَالَ اللَّهُ يَا عِيسَىٰ إِنِّي مُتَوَفِّيكَ وَرَافِعُكَ إِلَيَّ وَمُطَهِّرُكَ مِنَ الَّذِينَ كَفَرُوا وَجَاعِلُ الَّذِينَ اتَّبَعُوكَ فَوْقَ الَّذِينَ كَفَرُوا إِلَىٰ يَوْمِ الْقِيَامَةِ ۖ ثُمَّ إِلَيَّ مَرْجِعُكُمْ فَأَحْكُمُ بَيْنَكُمْ فِيمَا كُنتُمْ فِيهِ تَخْتَلِفُونَ (55) }

Nígbà tí (Ànábì) ‘Īsā fura sí àìgbàgbọ́ lọ́dọ̀ wọn (pé wọ́n fẹ́ pa òun), ó sọ pé: “Ta ni olùrànlọ́wọ́ mi sí ọ̀dọ̀ Allāhu?” Àwọn ọmọlẹ́yìn (rẹ̀) sọ pé: "Àwa ni olùrànlọ́wọ́ fún (ẹ̀sìn) Allāhu. A gba Allāhu gbọ́. Kí o sì jẹ́rìí pé dájúdájú mùsùlùmí ni wá.

Olúwa wa, a gbàgbọ́ nínú ohun tí O sọ̀kalẹ̀. A sì tẹ̀lé Òjíṣẹ́. Nítorí náà, kọ wá mọ́ àwọn olùjẹ́rìí."

Wọ́n déte, Allāhu sì déte. Allāhu sì l'óore jùlọ nínú àwọn adéte.

(Ẹ rántí) nígbà tí Allāhu sọ pé: "'Īsā, dájúdájú Mo máa gbà ọ́ (kúrò lọ́wọ́ wọn).1 Mo máa gbé ọ wá sókè lọ́dọ̀ Mi. Mo sì máa fọ̀ ọ́ mọ́ lọ́dọ̀ àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́.2 Mo sì máa fi àwọn t'ó tẹ̀lé ọ borí àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́ títí di Ọjọ́ Àjíǹde. Lẹ́yìn náà, ọ̀dọ̀ Mi ni ibùpadàsí yín. Mo sì máa ṣe ìdájọ́ láàárin yín nípa ohun tí ẹ yapa ẹnu sí. Aal-Imraan 52-55 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe àwọn ìjọ Anọbi Solih gbèrò láti pa a, wọn da ète, Ọlọhun naa si da ète si wọn, O si pa wọn run ati ìjọ wọn lapapọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{قَالُوا تَقَاسَمُوا بِاللَّهِ لَنُبَيِّتَنَّهُ وَأَهْلَهُ ثُمَّ لَنَقُولَنَّ لِوَلِيِّهِ مَا شَهِدْنَا مَهْلِكَ أَهْلِهِ وَإِنَّا لَصَادِقُونَ (49) وَمَكَرُوا مَكْرًا وَمَكَرْنَا مَكْرًا وَهُمْ لَا يَشْعُرُونَ (50) فَانظُرْ كَيْفَ كَانَ عَاقِبَةُ مَكْرِهِمْ أَنَّا دَمَّرْنَاهُمْ وَقَوْمَهُمْ أَجْمَعِينَ (51) }

Wọ́n wí (fúnra wọn) pé: "Kí á dìjọ fi Allāhu búra pé dájúdájú a máa pa òun àti àwọn ènìyàn rẹ̀ ní òru. Lẹ́yìn náà, dájúdájú a máa sọ fún ẹbí rẹ̀ pé ìparun àwọn ènìyàn rẹ̀ kò ṣojú wa. Dájúdájú olódodo sì ni àwa."

Wọ́n déte gan-an, Àwa náà sì déte gan-an, wọn kò sì fura.

Wo bí àtubọ̀tán ète wọn ti rí. Dájúdájú A pa àwọn àti ìjọ wọn run pátápátá. An-Nam'l 49-51

Islam kọ olè-jíjà, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«لاَ يَزْنِي الزَّانِي حِينَ يَزْنِي وَهُوَ مُؤْمِنٌ وَلاَ يَسْرِقُ حِينَ يَسْرِقُ وَهُوَ مُؤْمِنٌ وَلاَ يَشْرَبُ حِينَ يَشْرَبُهَا وَهُوَ مُؤْمِنٌ وَالتَّوْبَةُ مَعْرُوضَةٌ بَعْدُ»

Onişina ko nii maa ṣe ṣina nígbà tí ó bá n ṣe e ki o tun maa jẹ onigbagbọ, olè ko nii maa jalè nígbà tí ó bá n

jalè ki o tún máa jẹ onigbagbọ, ọmuti naa ko nii maa jẹ onigbagbọ nígbà tí ó bá n mu ọtí lọ́wọ́, ṣùgbọ́n ààyè ṣi wa fun ẹni tí o ṣe àwọn nkan wọnyi lati tuuba lẹyin ti o ba ṣe e tan. Sọhiihu ti Buhari 6810

Islam kọ ìkọjá-ààlà, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{إِنَّ اللَّهَ يَأْمُرُ بِالْعَدْلِ وَالْإِحْسَانِ وَإِيتَاءِ ذِي الْقُرْبَىٰ وَيَنْهَىٰ عَنِ الْفَحْشَاءِ وَالْمُنكَرِ وَالْبَغْيِ ۚ يَعِظُكُمْ لَعَلَّكُمْ تَذَكَّرُونَ }

Dájúdájú Allāhu ń pàṣẹ ṣíṣe déédé, ṣíṣe rere àti fífún ẹbí (ní ǹǹkan). Ó sì ń kọ ìwà ìbàjẹ́, ohun burúkú àti rúkèrúdò. Ó ń ṣe wáàsí fun yín nítorí kí ẹ lè lo ìrántí. An-Nah'l 90 Ojiṣẹ Olohun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«إنَّ الله أوحى إليَّ أن تَواضَعُوا حتى لا يَبغِي أحدٌ على أحدٍ ولا يفخَرَ أحدٌ على أحدٍ»

Dájúdájú Ọlọhun ránṣẹ́ si mi pe ki ẹ maa tẹrí ba fun ara yín ti ẹni kankan ko fi nii maa ṣe àbòsí fún ẹlòmíràn, ti ẹni kankan ko si tun nii maa ṣe faari si ẹlomiran Sọhiihu ti Abu Daaud 4895

Islam kọ àbòsí, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَٱللَّهُ لَا يُحِبُّ ٱلظَّـٰلِمِينَ}

Allāhu kò sì fẹ́ràn àwọn alábòsí Aal-Imraan 57 Allah tun sọ pe:

{ إِنَّهُۥ لَا يُفۡلِحُ ٱلظَّـٰلِمُونَ}

Dájúdájú àwọn alábòsí kò níí jèrè. Al-An'aam 21 Allah tun sọ pe:

{ وَٱلظَّـٰلِمِينَ أَعَدَّ لَهُمۡ عَذَابًا أَلِيمًۢا}

(Ní ti) àwọn alábòsí, Ó sì pèsè ìyà ẹlẹ́ta-eléro sílẹ̀ dè wọ́n. Al-In'saan 31 Ojiṣẹ Olohun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«ثَلَاثَةٌ لَا تُرَدُّ دَعْوَتُهُمْ: الْإِمَامُ الْعَادِلُ وَالصَّائِمُ حَتَّى يُفْطِرَ وَدَعْوَةُ الْمَظْلُومِ تُحْمَلُ عَلَى الْغَمَامِ وَتُفْتَحُ لَهَا أَبْوَابُ السَّمَاوَاتِ وَيَقُولُ الرَّبُّ عَزَّ وَجَلَّ: وَعِزَّتِي لَأَنْصُرَنَّكَ وَلَوْ بَعْدَ حِينٍ»

Àwọn mẹ́ta kan n bẹ ti wọn ko nii da ipepe wọn padà: Aṣiwaju ti o jẹ onideede, ati alaawẹ titi yóò fi ṣinu, ati ipepe ẹni tí a ṣe àbòsí sí, torí pé ipepe rẹ wọn yóò gbe e gorí ẹsujo, wọn yoo wa ṣi àwọn ilẹkun sánmọ̀ fun un, Olúwa ti O ni agbára ti O gbọnngbọn yóò wa sọ pe: Mo fi agbára Mi búra, bo pẹ bo ya Maa ran ẹ lọ́wọ́. Muslim ni o gbe e jáde (2749) ni ṣókí pẹ̀lú ìyàtọ̀ díẹ̀, ati Tirmiziy (2526) pẹ̀lú ìyàtọ̀ díẹ̀, ati Ahmad (8043) tiẹ̀ si ni gbólóhùn náà. Nígbà tí Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- rán Muaz lọ si Yemen, lára nkan ti ó sọ fún un ni pé:

«وَاتَّقِ دَعْوَةَ المَظْلُومِ فَإِنَّهُ لَيْسَ بَيْنَهُ وَبَيْنَ اللَّهِ حِجَابٌ»

ṣọ́ra fun ipepe ẹni tí a ṣe àbòsí si, torí pé ko si gaga láàrin rẹ àti aarin Ọlọhun Sohiihu ti Al-Bukhaar 1496 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«أَلَا مَن ظَلَم مُعاهِداً أو انتَقصَهُ أو كلَّفَهُ فوقَ طاقَتِه أو أخَذ منهُ شيئاً بِغيرِ طِيبِ نَفسٍ فأنا حَجِيجُهُ يوم القيامةِ»

Ẹ tẹti ẹ gbọ́, ẹnikẹ́ni ti o ba ṣe àbòsí fún ẹni tí a ṣe àdéhùn fun nínú àwọn Kèfèrí, tabi o din ẹtọ rẹ ku, tabi o la nnkan ti ko lágbára bọ ọ lọrun, tàbí o gba nnkan kan lọ́wọ́ rẹ̀ ti inú rẹ ko dun si, èmi (Anọbi) gan ni màá ba onítọ̀hún ja ni ọjọ igbende alukiyaamọ. Sunanu Abu

Daaud 3052 Islam- gẹ́gẹ́ bí ìwọ naa ti ri i- o n kọ gbogbo ìwà ti ko dára tàbí ibalopọ ti àbòsí.

## Islām n kọ ibalopọ ti owó ti èlé ba wa ninu ẹ, tabi ìnira, tabi ẹtanjẹ, tabi àbòsí, tàbí irẹjẹ, tàbí nnkan ti o ba le ṣe okunfa inira ti o maa kárí àwùjọ ati awọn ọmọ ìlú ati ẹni kọọkan.

Islām n kọ ibalopọ ti owó ti èlé ba wa ninu ẹ, tabi ìnira, tabi ẹtanjẹ, tabi àbòsí, tàbí irẹjẹ, tàbí nnkan ti o ba le ṣe okunfa inira ti o maa kárí àwùjọ ati awọn ọmọ ìlú ati ẹni kọọkan. A ti dárúkọ ṣíwájú ni ìbẹ̀rẹ̀ ipinrọ yii àwọn Aaya ati Hadiisi ti o n ṣe èlé ni eewọ, tabi àbòsí, tabi irẹjẹ, tabi ibajẹ ni orilẹ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَالَّذِينَ يُؤْذُونَ الْمُؤْمِنِينَ وَالْمُؤْمِنَاتِ بِغَيْرِ مَا اكْتَسَبُوا فَقَدِ احْتَمَلُوا بُهْتَانًا وَإِثْمًا مُّبِينًا}

Àwọn t'ó ń fi ìnira kan àwọn onígbàgbọ́ òdodo lọ́kùnrin àti onígbàgbọ́ òdodo lóbìnrin nípa ǹǹkan tí wọn kò ṣe, dájúdájú wọ́n ti ru ẹrù (ọ̀ràn) ìparọ́mọ́ni àti ẹ̀ṣẹ̀ pọ́nńbélé. Al-Ah'zaab 58 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ-tun sọ pe:

{مَّنْ عَمِلَ صَالِحًا فَلِنَفْسِهِ ۖ وَمَنْ أَسَاءَ فَعَلَيْهَا ۗ وَمَا رَبُّكَ بِظَلَّامٍ لِّلْعَبِيدِ}

Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere, ó ṣe é fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì ṣe aburú, ó ṣe é fún ẹ̀mí ara rẹ̀. Olúwa rẹ kò sì níí ṣe àbòsí sí àwọn ẹrúsìn. Fussilat:46

وجاء في السنة: «أَنَّ رَسُولَ اللَّهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ قَضَى أَنْ لَا ضَرَرَ وَلَا ضِرَارَ»

O wa ninu Sunna pe: "Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ṣe ìdájọ́ pe ki èèyàn ma ṣe nkan ti o le mu ìnira wa, ki èèyàn ma ṣe fi ara ni ẹni ti o ba fi ara ni èèyàn pada Sunanu Abu Daaud Ojiṣẹ Ọlọhun - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pe:

« مَن كانَ يُؤْمِنُ باللَّهِ والْيَومِ الآخِرِ فلا يُؤْذِي جارَهُ، ومَن كانَ يُؤْمِنُ باللَّهِ والْيَومِ الآخِرِ فَلْيُكْرِمْ ضَيْفَهُ، ومَن كانَ يُؤْمِنُ باللَّهِ والْيَومِ الآخِرِ فَلْيَقُلْ خَيْرًا، أوْ لِيسْكُتْ. وفي روايةٍ: فَلْيُحْسِنْ إلى جارِهِ. »

Ẹni ti o ba gba Ọlọhun gbọ ati ọjọ́ ìkẹyìn, ki o ma ṣe fi ṣuta kan alamuleti rẹ, ẹni ti o ba gba Ọlọhun gbọ ati ọjọ́ ìkẹyìn, ki o yaa maa pọn àlejò rẹ le, ẹni ti o ba gba Ọlọhun gbọ ati ọjọ́ ìkẹyìn, ki o yaa maa sọ dáadáa jáde ni ẹnu tabi ki o dakẹ. Ninu ẹgbawa miran, o wa nibẹ pe: Ki o yaa maa ṣe dáadáa si alamuleti rẹ. Sohiihu Muslim: 47 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«عُذِّبَتِ امْرَأَةٌ فِي هِرَّةٍ سَجَنَتْهَا حَتَّى مَاتَتْ فَدَخَلَتْ فِيهَا النَّارَ لَا هِيَ أَطْعَمَتْهَا وَسَقَتْهَا إِذْ هِيَ حَبَسَتْهَا وَلَا هِيَ تَرَكَتْهَا تَأْكُلُ مِنْ خَشَاشِ الْأَرْضِ»

Wọn fi ìyà jẹ arábìnrin kan látàrí olongbo kan ti o ti mọ ẹwọn titi o fi kú, o si ti ara rẹ̀ wọ iná, ko fun un ni oúnjẹ, ko si fun un ni nnkan mu, o de e mọlẹ, ko si tu u silẹ ki o maa jẹ nínú kòkòrò ilẹ̀. Sohiihu ti Al-Bukhaar 3482 Eleyii nipa ẹni tí ó fi suta kan olongbo, ka mai tii sọ ẹni tí o fi suta kan ọmọniyan. Lati ọdọ Ibnu Umar, o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- gun minbari, o wa pe pẹ̀lú ohun òkè lẹniti o sọ pe:

(يَا مَعْشَرَ مَنْ أَسْلَمَ بِلِسَانِهِ وَلَمْ يُفْضِ الإِيمَانُ إِلَى قَلْبِهِ لاَ تُؤْذُوا الْمُسْلِمِينَ وَلاَ تُعَيِّرُوهُمْ وَلاَ تَتَّبِعُوا عَوْرَاتِهِمْ فَإِنَّهُ مَنْ تَتَبَّعَ عَوْرَةَ أَخِيهِ الْمُسْلِمِ تَتَبَّعَ اللَّهُ عَوْرَتَهُ

وَمَنْ تَتَبَّعَ اللَّهُ عَوْرَتَهُ يَفْضَحْهُ وَلَوْ فِي جَوْفِ رَحْلِهِ قَالَ: وَنَظَرَ ابْنُ عُمَرَ يَوْمًا إِلَى الْبَيْتِ أَوْ إِلَى الكَعْبَةِ فَقَالَ: مَا أَعْظَمَكِ وَأَعْظَمَ حُرْمَتَكِ وَالمُؤْمِنُ أَعْظَمُ حُرْمَةً عِنْدَ اللهِ مِنْكِ)

Mo pe ẹyin ti ẹ gba Islām pẹ̀lú ahọ́n ti ìgbàgbọ́ koi tii de ọkàn yin, e o gbọdọ̀ fi suta kan àwọn Musulumi, ẹ o si gbọdọ bu wọn, ẹ o si gbọdọ maa wa ọna lati fi àléébù wọn han, torí pé ẹni tí ó bá n wa ọna láti fi àléébù ọmọ ìyá rẹ ti o jẹ Musulumi han, Ọlọhun yóò fi àléébù tiẹ̀ náà hàn, ẹni tí Ọlọhun ba si fi àléébù rẹ hàn, yóò dójú ti i, kódà ki o wa nínú yàrá rẹ, o sọ pe: Ibnu Umar wo Kaaba ni ọjọ kan ni o wa sọ pe: O ma tobi o! ọwọ rẹ naa si tobi!, ṣùgbọ́n onigbagbọ ni ọwọ ju ọ lọ ni ọdọ Ọlọhun. Tirmiziy ni o gbe e jade (2032), ati Ibnu Hibbaan (5763) Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

(مَنْ كَانَ يُؤْمِنُ بِاللَّهِ وَاليَوْمِ الآخِرِ فَلاَ يُؤْذِ جَارَهُ وَمَنْ كَانَ يُؤْمِنُ بِاللَّهِ وَاليَوْمِ الآخِرِ فَلْيُكْرِمْ ضَيْفَهُ وَمَنْ كَانَ يُؤْمِنُ بِاللَّهِ وَاليَوْمِ الآخِرِ فَلْيَقُلْ خَيْرًا أَوْ لِيَصْمُتْ)

Ẹnikẹ́ni ti o ba gba Ọlọhun gbọ ati ọjọ́ ìkẹyìn, ko gbọdọ fi suta kan alamuleti rẹ, ẹnikẹ́ni ti o ba gba Ọlọhun gbọ ati ọjọ́ ìkẹyìn, ki o maa pọn àlejò rẹ le, ẹnikẹ́ni ti o ba gba Ọlọhun gbọ ati ọjọ́ ìkẹyìn, ki o maa sọ dáadáa jáde lẹnu tabi ki o dakẹ. Sohiihu ti Al-Bukhaar 6018

وعَنْ أَبِي هُرَيْرَةَ عَنِ النَّبِيِّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ قَالَ: " هَلْ تَدْرُونَ مَنِ الْمُفْلِسُ؟ " قَالُوا: الْمُفْلِسُ فِينَا يَا رَسُولَ اللهِ مَنْ لَا دِرْهَمَ لَهُ وَلَا مَتَاعَ. قَالَ: " إِنَّ الْمُفْلِسَ مِنْ أُمَّتِي مَنْ يَأْتِي يَوْمَ الْقِيَامَةِ بِصِيَامٍ وَصَلَاةٍ وَزَكَاةٍ وَيَأْتِي قَدْ شَتَمَ عِرْضَ هَذَا وَقَذَفَ هَذَا وَأَكَلَ مَالَ هَذَا فَيُقْعَدُ فَيَقُصُّ هَذَا مِنْ حَسَنَاتِهِ وَهَذَا مِنْ حَسَنَاتِهِ فَإِنْ فَنِيَتْ حَسَنَاتُهُ قَبْلَ أَنْ يَقْضِيَ مَا عَلَيْهِ مِنَ الْخَطَايَا أُخِذَ مِنْ خَطَايَاهُمْ فَطُرِحَتْ عَلَيْهِ ثُمَّ طُرِحَ فِي النَّارِ)

Lati ọdọ Abu Huraira, lati ọdọ Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- o sọ pé: Ǹjẹ́ ẹyin mọ tani olọṣi? Wọn sọ pé olọṣi ninu wa, irẹ Ojiṣẹ Ọlọhun, oun naa ni ẹni tí ko ni owó ti ko si ni dúkìá. O sọ pe: "Dájúdájú olọṣi ninu ijọ mi ni ẹni tí yóò wa ni ọjọ́ igbende pẹ̀lú aawẹ àti irun ati saka, yóò tun wa wá pẹ̀lú pe o ti bu eléyìí, o parọ ṣina mọ eléyìí, o jẹ dukia eléyìí ni ọna aitọ, wọn yóò wa da a joko sílẹ̀, eleyii yóò gba ninu iṣẹ-rere rẹ, tọun naa yóò gba ninu iṣẹ-rere rẹ, ti iṣẹ-rere ba ti wa tan ṣíwájú ki o to san gbese gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ ti o wa lọrun rẹ, wọn yóò mu nínú ẹ̀ṣẹ̀ wọn, wọn yóò da a le e lórí, wọn yóò wa ju u sínú iná" Muslim ni o gbe e jade (2581), ati Tirmiziy (2418), ati Ahmad (8029), ti ẹ si ni gbólóhùn náà.

Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

(كَانَ عَلَى الطَّرِيقِ غُصْنُ شَجَرَةٍ يُؤْذِي النَّاسَ فَأَمَاطَهَا رَجُلٌ فَأُدْخِلَ الْجَنَّةَ)

"Ẹka igi kan n bẹ ni ojú ọna ti o n ko suta ba àwọn èèyàn, arákùnrin kan si mu u kúrò lọ́nà, o si ti ara rẹ wọ alujanna" Buhari ni o gbe e jade (652) pẹ̀lú ìtumọ̀ rẹ, ati Muslim (1914) pẹ̀lú nnkan ti o jọ bẹ́ẹ̀, ati Ibnu Maajah (3682), ati Ahmad (10432) ti àwọn méjèèjì si ni gbólóhùn náà, mímú suta kuro lọna maa n mu èèyàn wọ alujanna, kini o wa lérò pe o maa ṣẹlẹ̀ si ẹni tí n fi suta kan àwọn èèyàn, ti o si n ba ayé wọn jẹ

## Islām wa lati wa da aabo bo làákàyè ati lati ṣe gbogbo nkan ti o ba le ba a jẹ ni eewọ gẹ́gẹ́ bí mímu ọtí, o pàtàkì

**làákàyè, o ṣe e ni okunfa lila nnkan bọni lọrun, o si la a kúrò nibi àjàgà itankitan ati ibọrisa. Ko si si awọn àṣírí ikọkọ kankan ninu Islām, bẹ́ẹ̀ si ni ko si awọn idajọ kankan ti o wa fun àwọn ipò kan nikan ti ko kan òmíràn, gbogbo àwọn ìdájọ́ rẹ ati òfin rẹ pátá ni o ba làákàyè ti o ni alaafia mu, o si wa ni ibamu si nnkan ti déédéé ati ọgbọn n tọka si.**

Islam wa pẹ̀lú dídá ààbò bo làákàyè, o si pàtàkì rẹ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{إِنَّ السَّمْعَ وَالْبَصَرَ وَالْفُؤَادَ كُلُّ أُولَٰئِكَ كَانَ عَنْهُ مَسْئُولًا }

Dájúdájú ìgbọ́rọ̀, ìríran àti ọkàn; ìkọ̀ọ̀kan ìwọ̀nyẹn ni A óò bèèrè nípa rẹ̀. Al-Isroo 36 Dandan ni fun ọmọniyan ki o dáàbò bo làákàyè rẹ, torí ẹ ni Islām ṣe ṣe ọtí àti oogun olóró ni eewọ, mo si ti sọ nípa ṣíṣe ọtí ni eewọ ni ipinrọ ti nọ́mbà rẹ jẹ (34), ti ọpọlọpọ nínú àwọn aaya Kuraani si maa n parí pẹ̀lú gbólóhùn Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- pe:

{لَعَلَّكُمْ تَعْقِلُونَ}

nítorí kí ẹ lè ṣe làákàyè Al-Baqara 242 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{وَمَا الْحَيَاةُ الدُّنْيَا إِلَّا لَعِبٌ وَلَهْوٌ ۖ وَلَلدَّارُ الْآخِرَةُ خَيْرٌ لِّلَّذِينَ يَتَّقُونَ ۗ أَفَلَا تَعْقِلُونَ }

Ìṣẹ̀mí ayé kò sì jẹ́ kiní kan bí kò ṣe eré àti ìranù. Ọgbà Ìkẹ́yìn sì lóore jùlọ fún àwọn t’ó ń bẹ̀rù (Allāhu). Ṣé ẹ ò ṣe làákàyè ni? Al-An'aam 32 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{ إِنَّا أَنزَلْنَاهُ قُرْآنًا عَرَبِيًّا لَّعَلَّكُمْ تَعْقِلُونَ }

Dájúdájú Àwa sọ̀ ọ́ kalẹ̀ ní ǹǹkan kíké ní èdè Lárúbáwá nítorí kí ẹ lè ṣe làákàyè. Yuusuf: 2 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- wa ṣàlàyé pe imọna ati ọgbọn, ko si ẹni ti yóò ṣe àǹfààní latara méjèèjì ju àwọn oni làákàyè lọ, àwọn naa si ni àwọn ọlọ́gbọ́n, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{يُؤْتِي الْحِكْمَةَ مَن يَشَاءُ ۚ وَمَن يُؤْتَ الْحِكْمَةَ فَقَدْ أُوتِيَ خَيْرًا كَثِيرًا ۗ وَمَا يَذَّكَّرُ إِلَّا أُولُو الْأَلْبَابِ }

Ó ń fún ẹni tí Ó bá fẹ́ ní òye ìjìnlẹ̀. Ẹni tí A bá sì fún ní òye ìjìnlẹ̀, A kúkú ti fún un ní oore púpọ̀. Ẹnì kan kò níí lo ìrántí àfi àwọn onílàákàyè. Al-Baqara: 269

Fun ìdí eyi ni Islam ṣe ṣe làákàyè ni okùnfà lila nnkan bọni lọrun, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé:

«رُفِعَ الْقَلَمُ عَنْ ثَلَاثٍ: عَنِ النَّائِمِ حَتَّى يَسْتَيْقِظَ وَعَنِ الصَّبِيِّ حَتَّى يَحْتَلِمَ وَعَنِ الْمَجْنُونِ حَتَّى يَعْقِلَ»

"Wọn ti gbe kálámù sókè nibi nkan mẹ́ta kan: Ẹni ti o n sun títí yóò fi jí, ati ọmọkekere titi yóò fi bàlágà, ati weere titi yóò fi ni làákàyè" Buhari gbe e jade lẹniti o ti parẹ ninu awọn ti wọn gba a wa pẹ̀lú gbólóhùn amọdaju síwájú hadiisi (5269) pẹ̀lú nnkan ti o jọ bẹ́ẹ̀. Abu Daaud gbe e jade lai pa ẹni kankan rẹ ninu awọn

ti wọn gba a wa (4402), tiẹ si ni gbólóhùn naa, ati Tirmiziy (1423), ati An-Nasaa'i ninu (As-Sunanul Kubrọ) (7346), ati Ahmad (956) pẹ̀lú ìyàtọ̀ díẹ̀, ati Ibnu Maajah (2042) ni ṣókí O la a kúrò nibi àjàgà itankitan ati ibọrisa, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ nipa iṣesi àwọn ìjọ bi wọn ṣe dirọ mọ àwọn itankitan, ati bi wọn ṣe kọ òdodo ti o wa lati ọdọ Ọlọhun:

{وَكَذَٰلِكَ مَا أَرْسَلْنَا مِن قَبْلِكَ فِي قَرْيَةٍ مِّن نَّذِيرٍ إِلَّا قَالَ مُتْرَفُوهَا إِنَّا وَجَدْنَا آبَاءَنَا عَلَىٰ أُمَّةٍ وَإِنَّا عَلَىٰ آثَارِهِم مُّقْتَدُونَ}

Bákan náà, Àwa kò rán olùkìlọ̀ kan sí ìlú kan ṣíwájú rẹ, àyàfi kí àwọn onígbẹdẹmukẹ ìlú náà wí pé: "Dájúdájú àwa bá àwọn bàbá wa lórí ẹ̀sìn kan. Dájúdájú àwa sì ni olùtẹ̀lé wọn lórí orípa wọn." Az-Zukhruf: 23 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ nípa Anọbi Ibrahim- ki ọlà Ọlọhun maa ba a- wipe o sọ fun àwọn ìjọ rẹ pe:

{مَا هَٰذِهِ التَّمَاثِيلُ الَّتِي أَنتُمْ لَهَا عَاكِفُونَ (52) قَالُوا وَجَدْنَا آبَاءَنَا لَهَا عَابِدِينَ (53)}

Kí ni àwọn ère wọ̀nyí tí ẹ̀ ń dúró tì lọ́rùn ṣe jẹ́ ná?"

Wọ́n wí pé: "A bá àwọn bàbá wa tí wọ́n ń jọ́sìn fún wọn ni." Al-Anbiyaa 52-53 Islam wa, o si pa àwọn èèyàn láṣẹ pe ki wọn fi jijọsin fun àwọn ooṣa silẹ, ki wọn si bọpa-bọsẹ kuro nibi awọn itankitan ti wọn jogún lati ọdọ àwọn bàbá wọn ati awọn baba-baba wọn, ki wọn si tẹle ojú ọna àwọn Ojiṣẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá wọn).

Àwọn àṣírí ikọkọ kankan ko si nínú Islām, bẹ́ẹ̀ si ni ko si awọn idajọ ti o wa fun eeyan ti won wa ni ipò kan nìkan ti ko kan òmíràn ninu ẹ

سُئل علي بن أبي طالب رضي الله عنه وهو ابن عم رسول الله صلى الله عليه وسلم وزوج ابنته: أَخَصَّكُمْ رَسُولُ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ بِشَيْءٍ؟ فَقَالَ: «مَا خَصَّنَا رَسُولُ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ بِشَيْءٍ لَمْ يَعُمَّ بِهِ النَّاسَ كَافَّةً إِلَّا مَا كَانَ فِي قِرَابِ سَيْفِي هَذَا قَالَ: فَأَخْرَجَ صَحِيفَةً مَكْتُوبٌ فِيهَا: لَعَنَ اللهُ مَنْ ذَبَحَ لِغَيْرِ اللهِ وَلَعَنَ اللهُ مَنْ سَرَقَ مَنَارَ الْأَرْضِ وَلَعَنَ اللهُ مَنْ لَعَنَ وَالِدَهُ وَلَعَنَ اللهُ مَنْ آوَى مُحْدِثًا»

Wọn bi Aliy ọmọ Abu Toolib- ki Ọlọhun yọ́nú si i- léèrè, oun si ni ọmọ ọmọ-iya baba Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- o si tun jẹ ọkọ ọmọ rẹ, wọn bi i léèrè pé: Ǹjẹ́ Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- da yin sa lẹsa pẹ̀lú nkankan bi? O sọ pé: Ko da wa sa lẹsa pẹ̀lú nnkan kan ti ko wa kan gbogbo àwọn èèyàn pátápátá àyàfi nnkan ti n bẹ ninu apo idà mi yìí, o sọ pe: O ba mu ìwé kan jáde ti wọn kọ sínú rẹ pé: Ọlọhun ṣẹ ibi le ẹni ti o ba du nkan fun nnkan ti o yatọ si Ọlọhun, Ọlọhun tun ṣẹ ibi le ẹni tí o ba paarọ àmì ààlà ilẹ̀, Ọlọhun tun ṣẹ ibi le ẹni tí ó bá ṣẹ ibi le bàbá rẹ̀, Ọlọhun tun ṣẹ ibi le ẹni tí o ba n dáàbò bo ọ̀daràn" Sohiihu Muslim: 1978 Gbogbo àwọn ìdájọ́ Islām ati òfin rẹ pátá ni o ba làákàyè ti o ni alaafia mu, o si wa ni ibamu si nnkan ti déédéé ati ọgbọn n tọka si.

## Àwọn ẹ̀sìn irọ, ti àwọn ti wọn n ṣe e ko ba ni agbọye àwọn àtakò ti o wa ninu ẹ, ati awọn nnkan ti o tako làákàyè, àwọn àlùfáà ẹ̀sìn naa yoo jẹ ki awọn olutẹle wọn lérò pe ẹsin ju làákàyè lọ ni, ati pe ko si igbalaaye fun làákàyè lati gbọ ẹsin ye. Àmọ́ Islām ka ẹsin kun

**imọlẹ ti o maa tan si ojú ọna fun làákàyè, ti àwọn ti wọn n ṣe ẹsin irọ n fẹ ki awọn èèyàn pa làákàyè ti ki wọn si maa tẹle àwọn, ti Islām si n fẹ ki ọmọniyan ta làákàyè rẹ ji lati mọ pàtó bi àwọn ọ̀rọ̀ ṣe jẹ́ gan.**

Àwọn ẹ̀sìn irọ, ti àwọn ti wọn n ṣe e ko ba ni agbọye àwọn àtakò ti o wa ninu ẹ, ati awọn nnkan ti o tako làákàyè, àwọn àlùfáà ẹ̀sìn naa yoo jẹ ki awọn olutẹle wọn lérò pe ẹsin ju làákàyè lọ, ati pe ko si igbalaaye fun làákàyè lati gbọ ẹsin ye. Àmọ́ Islām ka ẹsin kun imọlẹ ti o maa tan si ojú ọna fun làákàyè, ti àwọn ti wọn n ṣe ẹsin irọ n fẹ ki awọn èèyàn pa làákàyè ti ki wọn si maa tẹle àwọn, ti Islām si n fẹ ki ọmọniyan ta làákàyè rẹ ji lati ronú jinlẹ, ati lati mọ pàtó bi àwọn ọ̀rọ̀ ṣe jẹ́ gan. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَكَذَٰلِكَ أَوْحَيْنَا إِلَيْكَ رُوحًا مِّنْ أَمْرِنَا ۚ مَا كُنتَ تَدْرِي مَا الْكِتَابُ وَلَا الْإِيمَانُ وَلَٰكِن جَعَلْنَاهُ نُورًا نَّهْدِي بِهِ مَن نَّشَاءُ مِنْ عِبَادِنَا ۚ وَإِنَّكَ لَتَهْدِي إِلَىٰ صِرَاطٍ مُّسْتَقِيمٍ }

Báyẹn sì ni A ṣe fi ìmísí ránṣẹ́ sí ọ nínú àṣẹ Wa. Ìwọ kò mọ kí ni Tírà àti ìgbàgbọ́ òdodo tẹ́lẹ̀ (ṣíwájú ìmísí náà),1 ṣùgbọ́n A ṣe ìmísí náà ní ìmọ́lẹ̀ kan tí À ń fi ṣe ìmọ̀nà fún ẹni tí A bá fẹ́ nínú àwọn ẹrúsìn Wa. Dájúdájú ìwọ ń pèpè sí ọ̀nà tààrà (’Islām). As-Shuura: 52 Imisi ti Ọlọhun ko àwọn ẹri sínú, ti àwọn ẹri naa yóò maa tọ làákàyè ti o ni alaafia sọna lọ sibi ododo to

n wa lati mọ ati lati gba a gbọ. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{يَا أَيُّهَا النَّاسُ قَدْ جَاءَكُم بُرْهَانٌ مِّن رَّبِّكُمْ وَأَنزَلْنَا إِلَيْكُمْ نُورًا مُّبِينًا}

Ẹ̀yin ènìyàn, dájúdájú ẹ̀rí ọ̀rọ̀ ti dé ba yín láti ọ̀dọ̀ Olúwa yín. A sì tún sọ ìmọ́lẹ̀ t'ó yanjú kalẹ̀ fun yín. An-Nisaa: 174 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n fẹ ki ọmọniyan maa ṣẹmi nínú imọlẹ imọna ati ìmọ̀ ati òdodo, ti àwọn ẹṣu si n fẹ ki ọmọniyan maa wa nínú okunkun kèfèrí ati aimọkan ati anu, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{اللَّهُ وَلِيُّ الَّذِينَ آمَنُوا يُخْرِجُهُم مِّنَ الظُّلُمَاتِ إِلَى النُّورِ ۖ وَالَّذِينَ كَفَرُوا أَوْلِيَاؤُهُمُ الطَّاغُوتُ يُخْرِجُونَهُم مِّنَ النُّورِ إِلَى الظُّلُمَاتِ}

Allāhu ni Aláràǹṣe àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo. Ó ń mú wọn jáde kúrò nínú àwọn òkùnkùn wá sínú ìmọ́lẹ̀. Àwọn t'ó sì ṣàì gbàgbọ́, àwọn òrìṣà ni aláfẹ̀yìntì wọn. Àwọn òrìṣà ń mú wọn jáde kúrò nínú ìmọ́lẹ̀ wá sínú àwọn òkùnkùn. Al-Baqara: 257

## Islam n babara imọ ti o ba ni alaafia, o si n ṣeni ni ojúkòkòrò lati maa ṣe iwadi ti imọ ti ko nii si ifẹ-inu ninu ẹ, o si tun n pepe si wiwoye ati rí ronú nipa ara wa ati nipa ayé ni àyíká wa, àwọn àbájáde ìwádìí ìmọ̀ ti o ba si ni àlàáfíà ko le tako Islam.

Islam n babara imọ ti o ba ni àlàáfíà, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{يَرْفَعِ اللَّهُ الَّذِينَ آمَنُوا مِنكُمْ وَالَّذِينَ أُوتُوا الْعِلْمَ دَرَجَاتٍ ۚ وَاللَّهُ بِمَا تَعْمَلُونَ خَبِيرٌ {

Allāhu yóò ṣàgbéga àwọn ipò fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo àti àwọn tí A fún ní ìmọ̀ nínú yín. Allāhu sì ni Alámọ̀tán nípa ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́. (Suratul Mujaadalah :11) Ọlọhun so ijẹri àwọn onimimọ papọ mọ ijẹri Rẹ ati ijẹri àwọn Malaika lori nnkan ti a n jẹri si ti o tobi ju

{شَهِدَ اللَّهُ أَنَّهُ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ وَالْمَلَائِكَةُ وَأُولُو الْعِلْمِ قَائِمًا بِالْقِسْطِ ۚ لَا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ الْعَزِيزُ الْحَكِيمُ }

Allāhu jẹ́rìí pé dájúdájú kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Àwọn mọlāika àti onímọ̀ ẹ̀sìn (tún jẹ́rìí bẹ́ẹ̀.), Allāhu ni Onídéédé. Kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. Aal Im'raan/18 Eleyii n ṣàlàyé ipò ti àwọn onimimọ wa nínú Islām, Ọlọhun ko si pa Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- láṣẹ lati wa alekun nnkan kan tayọ imọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَقُل رَّبِّ زِدْنِي عِلْمًا }

Kí o sì sọ pé: "Olúwa mi, ṣàlékún ìmọ̀ fún mi." Too'haa: 114 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«مَنْ سَلَكَ طَرِيقًا يَلْتَمِسُ فِيهِ عِلْمًا سَهَّلَ اللَّهُ لَهُ طَرِيقًا إِلَى الْجَنَّةِ وَإِنَّ الْمَلَائِكَةَ لَتَضَعُ أَجْنِحَتَهَا رِضًا لِطَالِبِ الْعِلْمِ وَإِنَّ طَالِبَ الْعِلْمِ يَسْتَغْفِرُ لَهُ مَنْ فِي السَّمَاءِ وَالْأَرْضِ حَتَّى الْحِيتَانِ فِي الْمَاءِ وَإِنَّ فَضْلَ الْعَالِمِ عَلَى الْعَابِدِ كَفَضْلِ الْقَمَرِ عَلَى سَائِرِ الْكَوَاكِبِ إِنَّ الْعُلَمَاءَ وَرَثَةُ الْأَنْبِيَاءِ إِنَّ الْأَنْبِيَاءَ لَمْ يُوَرِّثُوا دِينَارًا وَلَا دِرْهَمًا إِنَّمَا وَرَّثُوا الْعِلْمَ فَمَنْ أَخَذَهُ أَخَذَ بِحَظٍّ وَافِرٍ»

"Eniti o ba tọ oju ona kan leniti o n wa imo ni ibe, Ọlọhun a rọ ona kan fun un losi AL-Jannah, ati pe

awon Malaika yoo maa tẹ awon iyẹ won sile ni ẹni ti n yonu si ẹni ti o n wa imọ, atipe dajudaju ẹni tí ó n wá ìmọ̀, gbogbo nnkan ti n be ni sanmọ ati ilẹ ni yoo maa toro aforijin fun un titi de ori awon eja ti n be ninu omi, ati pe dajudaju ola ti n be fun onimimọ lori olusin Ọlọhun da gẹgẹ bii ọla ti n be fun osupa lori awon irawo yoku. Dajudaju awon onimimọ ni won jogun awon Anabi, awon Anabi o si fi diinar pelu dirham silẹ lati jogún, nnkan ti wọn fi silẹ naa ni imọ, ẹni ti o ba gba a mu, onitọun ti di ipin ti o pe mu". Abu Da'ud ni o gbe e jade (3641), ati Tirmidhiy (2682), ati Ibn Maajah (223) ati pe gbolohun yii tie ni, ati Ahmad (21715).

Islaam nṣe wa ni ojukokoro lori ṣiṣe iwadii ti o jẹ ti mimọ eleyi ti o bọra kuro nibi ìfẹ́-inu, ti o si n pepe lọ sibi iwoyesi ati rironu nipa ẹmi wa, ati nipa agbaye ti o yi wa ka. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- so pe:

{سَنُرِيهِمْ آيَاتِنَا فِي الْآفَاقِ وَفِي أَنفُسِهِمْ حَتَّىٰ يَتَبَيَّنَ لَهُمْ أَنَّهُ الْحَقُّ ۗ أَوَلَمْ يَكْفِ بِرَبِّكَ أَنَّهُ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ شَهِيدٌ}

A óò máa fi àwọn àmì Wa hàn wọ́n nínú òfurufú àti nínú ẹ̀mí ara wọn títí ó máa fi hàn kedere sí wọn pé dájúdájú al-Ḳur'ān ni òdodo. Ǹjẹ́ Olúwa rẹ kò tó kí ó jẹ́ pé dájúdájú Òun ni Arínú-róde lórí gbogbo ǹǹkan? Suuratu Fussilat: 53. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{أَوَلَمْ يَنظُرُوا فِي مَلَكُوتِ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَمَا خَلَقَ اللَّهُ مِن شَيْءٍ وَأَنْ عَسَىٰ أَن يَكُونَ قَدِ اقْتَرَبَ أَجَلُهُمْ ۖ فَبِأَيِّ حَدِيثٍ بَعْدَهُ يُؤْمِنُونَ}

Ṣé wọn kò wo ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ pẹ̀lú gbogbo ǹǹkan tí Allāhu dá? Àmọ́ sá ó lè jẹ́ pé Àkókò

ikú wọn ti súnmọ́. Nígbà náà, ọ̀rọ̀ wo ni wọn yóò gbàgbọ́ lẹ́yìn rẹ̀? Suuratul Ah’roof: 185. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{أَوَلَمْ يَسِيرُوا فِي الْأَرْضِ فَيَنظُرُوا كَيْفَ كَانَ عَاقِبَةُ الَّذِينَ مِن قَبْلِهِمْ ۚ كَانُوا أَشَدَّ مِنْهُمْ قُوَّةً وَأَثَارُوا الْأَرْضَ وَعَمَرُوهَا أَكْثَرَ مِمَّا عَمَرُوهَا وَجَاءَتْهُمْ رُسُلُهُم بِالْبَيِّنَاتِ ۖ فَمَا كَانَ اللَّهُ لِيَظْلِمَهُمْ وَلَٰكِن كَانُوا أَنفُسَهُمْ يَظْلِمُونَ}

Ṣé wọn kò rìn kiri lórí ilẹ̀ kí wọ́n wo bí ìkángun àwọn t’ó ṣíwájú wọn ṣe rí? Wọ́n ní agbára jù wọ́n lọ. Wọ́n fi ilẹ̀ dáko. Wọ́n sì lo ilẹ̀ fún ohun tí ó pọ̀ ju bí (àwọn ará Mọkkah) ṣe lò ó. Àwọn Òjíṣẹ́ wọn sì mú àwọn ẹ̀rí t’ó yanjú wá bá wọn. Nítorí náà, Allāhu kò ṣàbòsí sí wọn, ṣùgbọ́n ẹ̀mí ara wọn ni wọ́n ń ṣàbòsí sí. Suuratur Ruum: 9.

Atipe awon abajade (esi) ti o je ti mimo ti o si ni alaafia ko le wa ni itako pelu Islaam. Ati pe a maa so apejuwe kan ti Al-Qur’aan ti se awọn alaye ijinlẹ nipa rẹ ṣíwájú nnkan ti o le ni ẹgbẹ̀rún kan ati ọgọ́rùn-ún meerin odun, ti imo ijinle ode-oni ṣẹ̀ṣẹ̀ fi idi re mule ni igbehin-gbehin; awọn abajade imọ wa wa ni ibamu si nnkan ti o wa ninu Al-Qur’aa ti o tobi julọ, doun naa ni ṣiṣẹda ọlẹ-inu si inu ikun iya re. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَلَقَدْ خَلَقْنَا الْإِنسَانَ مِن سُلَالَةٍ مِّن طِينٍ (12) ثُمَّ جَعَلْنَاهُ نُطْفَةً فِي قَرَارٍ مَّكِينٍ (13) ثُمَّ خَلَقْنَا النُّطْفَةَ عَلَقَةً فَخَلَقْنَا الْعَلَقَةَ مُضْغَةً فَخَلَقْنَا الْمُضْغَةَ عِظَامًا فَكَسَوْنَا الْعِظَامَ لَحْمًا ثُمَّ أَنشَأْنَاهُ خَلْقًا آخَرَ ۚ فَتَبَارَكَ اللَّهُ أَحْسَنُ الْخَالِقِينَ (14)}

Dájúdájú A ti ṣe ẹ̀dá ènìyàn láti inú ohun tí A mọ jáde láti inú erùpẹ̀ amọ̀.

Lẹ́yìn náà, A ṣe é ní àtọ̀ sínú àyè ààbò (ìyẹn, ilé-ọmọ).

Lẹ́yìn náà, A sọ àtọ̀ di ẹ̀jẹ̀ dídì. Lẹ́yìn náà, A sọ ẹ̀jẹ̀ dídì di bááṣí ẹran. Lẹ́yìn náà, A sọ bááṣí ẹran di eegun. Lẹ́yìn náà, A fi ẹran bo eegun. Lẹ́yìn náà, A sọ ọ́ di ẹ̀dá mìíràn.1 Nítorí náà, ìbùkún ni fún Allāhu, Ẹni t'Ó dára jùlọ nínú àwọn ẹlẹ́dàá (oníṣẹ́-ọnà). Suuratul Muh'minuun: 12-14.

**40. Ati pe Ọlọhun ko nii gba iṣẹ, Ko si nii ṣe ẹsan le e lori ni ojo ikehin ayaafi ti o ba wa lati odo eniti o ni igbagbo pelu Olohun ti o si tun tele ase Re, ti o si tun gba awon ojise Re – ki ike ati ola maa ba won – ni ododo, ati pe Olohun ko nii gba ninu awon ijosin ayaafi èyí ti O ba se e lofin, nitori naa bawo wa ni omoniyan o se maa se aigbagbo pelu Olohun ti yoo wa maa reti ki o san an ni esan? Ati pe Olohun ko nii gba igbagbo enikeni ninu awon eeyan ayaafi ti o ba ni igbagbo si awon Anọbi- ki ola o maa ba gbogbo won lapapo- ti o si tun ni igbagbo si jije**

**ojise Muhammad (ki ike ati ola Olohun maa ba a).**

Ati pe Ọlọhun ko nii gba ise, Ko si ni san ẹsan le e lori ni ọjọ ikẹhin ayaafi ti o ba wa lati odo ẹni ti o ni igbagbo si Ọlọhun ti o si tun tele àṣẹ Rẹ, ti o si tun gba awọn ojiṣẹ Rẹ- ki ikẹ ati ọla maa ba wọn- ni ododo. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{مَّن كَانَ يُرِيدُ الْعَاجِلَةَ عَجَّلْنَا لَهُ فِيهَا مَا نَشَاءُ لِمَن نُّرِيدُ ثُمَّ جَعَلْنَا لَهُ جَهَنَّمَ يَصْلَاهَا مَذْمُومًا مَّدْحُورًا (18) وَمَنْ أَرَادَ الْآخِرَةَ وَسَعَىٰ لَهَا سَعْيَهَا وَهُوَ مُؤْمِنٌ فَأُولَٰئِكَ كَانَ سَعْيُهُم مَّشْكُورًا (19) }

Ẹni tí ó bá ń gbèrò (oore) ayé yìí (nìkan), A máa taari ohun tí A bá fẹ́ sí i nínú rẹ̀ ní kíákíá fún ẹni tí A bá fẹ́. Lẹ́yìn náà, A máa ṣe iná Jahanamọ fún un; ó máa wọ inú rẹ̀ ní ẹni yẹpẹrẹ, ẹni ẹ̀kọ̀.

Ẹni tí ó bá sì gbèrò (oore) ọ̀run, tí ó sì ṣe iṣẹ́ rẹ̀, ó sì jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo, àwọn wọ̀nyẹn, iṣẹ́ wọn máa jẹ́ àtẹ́wọ́gbà (pẹ̀lú ẹ̀san rere). Suuratul Is’raai: 18-19. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{ فَمَن يَعْمَلْ مِنَ الصَّالِحَاتِ وَهُوَ مُؤْمِنٌ فَلَا كُفْرَانَ لِسَعْيِهِ وَإِنَّا لَهُ كَاتِبُونَ}

Nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣe nínú àwọn iṣẹ́ rere, tí ó sì jẹ́ onígbàgbọ́ òdodo, kò sí kíkọ̀ fún iṣẹ́ rẹ̀. Àti pé dájúdájú Àwa máa ṣe àkọsílẹ̀ rẹ̀ fún un. Suurtul Anbiyaah: 94. Ati pe Ọlọhun ko nii gba ninu awọn ijọsin ayaafi eyi ti O ba ṣe e lofin. Ọlọhun- ti ola Re ga- sọ pe:

{ فَمَن كَانَ يَرْجُو لِقَاءَ رَبِّهِ فَلْيَعْمَلْ عَمَلًا صَالِحًا وَلَا يُشْرِكْ بِعِبَادَةِ رَبِّهِ أَحَدًا }

Nítorí náà, ẹnikẹ́ni tí ó bá ń retí ìpàdé Olúwa rẹ̀, kí ó ṣe iṣẹ́ rere. Kò sì gbọdọ̀ fi ẹnì kan kan ṣe akẹgbẹ́ níbi

jíjọ́sìn fún Olúwa rẹ̀.” Al-Kahf 110 O wa ṣàlàyé wipe dajudaju iṣẹ́ ko nii jẹ iṣẹ́ daadaa ayaafi ki o jẹ lati inu nnkan ti Ọlọhun ṣe ni ofin, ti ẹni ti ti o ni i si fi I'mọkanga fun Ọlọhun ninu iṣẹ́ rẹ, ti o si tun ni igbagbọ pẹlu Ọlọhun ti o si gba àwọn Anabi Rẹ ni ododo ati awọn Ojiṣẹ Rẹ– ki ọla Ọlọhun maa ba wọn– àmọ́ ẹni ti iṣẹ́ rẹ ba yàtọ̀ si iyẹn, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga- ti sọ pe:

{وَقَدِمْنَا إِلَىٰ مَا عَمِلُوا مِنْ عَمَلٍ فَجَعَلْنَاهُ هَبَاءً مَّنثُورًا }

Àti pé A máa wá ṣíbi ohun tí wọ́n ṣe níṣẹ́, A sì máa sọ ọ́ di eruku àfẹ́dànù. Suuratul Fur’qaan: 23. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{ وُجُوهٌ يَوْمَئِذٍ خَاشِعَةٌ (2) عَامِلَةٌ نَّاصِبَةٌ (3) تَصْلَىٰ نَارًا حَامِيَةً (4) }

Àwọn ojú kan yóò wálẹ̀ (ní ti ìyẹpẹrẹ) ní ọjọ́ yẹn.
Oníṣẹ́ àṣekúdórógbó (ni wọ́n nílé ayé). (3)
Wọ́n máa wọ inú Iná t’ó gbóná janjan (ní ọ̀run). (4)

Suuratul Gooshiyah: 2-4. Awọn oju yii yoo walẹ (ni ti ìyẹpẹrẹ) yoo si ṣe aṣeekudorogbo iṣẹ́, àmọ́ latari wipe o n ṣiṣẹ́ pẹlu nnkan ti o yàtọ̀ si imọna lati ọdọ Ọlọhun; Ọlọhun ṣe ina ni ibuṣẹri si rẹ; nítorí pe wọn ko ṣe iṣẹ́ pẹlu nnkan ti o yàtọ̀ si nnkan ti Ọlọhun ṣe ni ofin nikan, bi ko ṣe wipe wọn tun jọsin pẹlu awọn ijọsin burúkú, wọn si tun tẹle awọn olori anu àwọn ti wọn n da adadaalẹ awọn ẹsin buruku fun wọn. Nitori naa, iṣẹ́ daadaa eleyi ti yoo jẹ atẹwọgba ni ọdọ Ọlọhun naa ni eleyi ti o ṣe deede pẹlu nnkan ti Ojiṣẹ– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a– mu wa. Ati pe bawo ni ọmọniyan o ṣe maa ṣe aìgbàgbọ́ si Ọlọhun, ti yoo si maa reti ki O ṣẹsan fun un.

Ati pe Ọlọhun ko nii gba igbagbọ ẹnikẹni ninu awọn eeyan ayaafi ti o ba ni igbagbọ si awọn Anabi– ki ọla Ọlọhun maa ba gbogbo wọn lapapọ– ti o si tun ni igbagbọ si jíjẹ́ ojiṣẹ Muhammad– ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- a si ti sọ awọn ẹri kan síwájú lori ìyẹn ni ipinro ogun (20). Ọlọhun ti ọla Rẹ ga- tun sọ pe:

{آمَنَ الرَّسُولُ بِمَا أُنزِلَ إِلَيْهِ مِن رَّبِّهِ وَالْمُؤْمِنُونَ ۚ كُلٌّ آمَنَ بِاللَّهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ لَا نُفَرِّقُ بَيْنَ أَحَدٍ مِّن رُّسُلِهِ ۚ وَقَالُوا سَمِعْنَا وَأَطَعْنَا ۖ غُفْرَانَكَ رَبَّنَا وَإِلَيْكَ الْمَصِيرُ}

Òjíṣẹ́ náà (sollalāhu 'alayhi wa sallam) gbàgbọ́ nínú ohun tí wọ́n sọ̀kalẹ̀ fún un láti ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ̀. Àwọn onígbàgbọ́ òdodo náà (gbàgbọ́ nínú rẹ̀). Ẹnì kọ̀ọ̀kan (wọn) gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀ àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. A kò ya ẹnì kan sọ́tọ̀ nínú àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Wọ́n sì sọ pé: “A gbọ́ (àṣẹ), a sì tẹ̀lé (àṣẹ). À ń tọrọ àforíjìn Rẹ, Olúwa wa. Ọ̀dọ̀ Rẹ sì ni àbọ̀ ẹ̀dá.” Suuratul Baqara: 285 Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{يَا أَيُّهَا الَّذِينَ آمَنُوا آمِنُوا بِاللَّهِ وَرَسُولِهِ وَالْكِتَابِ الَّذِي نَزَّلَ عَلَىٰ رَسُولِهِ وَالْكِتَابِ الَّذِي أَنزَلَ مِن قَبْلُ ۚ وَمَن يَكْفُرْ بِاللَّهِ وَمَلَائِكَتِهِ وَكُتُبِهِ وَرُسُلِهِ وَالْيَوْمِ الْآخِرِ فَقَدْ ضَلَّ ضَلَالًا بَعِيدًا}

Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ gbàgbọ́ dáadáa nínú Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀, àti Tírà tí (Allāhu) sọ̀kalẹ̀ fún Òjíṣẹ́ Rẹ̀, àti Tírà tí Ó sọ̀kalẹ̀ ṣíwájú. Ẹnikẹ́ni tí ó bá ṣàì gbàgbọ́ nínú Allāhu, àwọn mọlāika Rẹ̀, àwọn Tírà Rẹ̀, àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀ àti Ọjọ́ Ìkẹyìn, dájúdájú ó ti ṣìnà ní ìṣìnà t’ó jìnnà tefétefé. Suuratun-Nisai: 136. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ- tun sọ pe:

{وَإِذْ أَخَذَ اللَّهُ مِيثَاقَ النَّبِيِّينَ لَمَا آتَيْتُكُم مِّن كِتَابٍ وَحِكْمَةٍ ثُمَّ جَاءَكُمْ رَسُولٌ مُّصَدِّقٌ لِّمَا مَعَكُمْ لَتُؤْمِنُنَّ بِهِ وَلَتَنصُرُنَّهُ ۚ قَالَ أَأَقْرَرْتُمْ وَأَخَذْتُمْ عَلَىٰ ذَٰلِكُمْ إِصْرِي ۖ قَالُوا أَقْرَرْنَا ۚ قَالَ فَاشْهَدُوا وَأَنَا مَعَكُم مِّنَ الشَّاهِدِينَ}

(Ẹ rántí) nígbà tí Allāhu gba àdéhùn lọ́wọ́ àwọn Ànábì pé: "(Ẹ lo) èyí tí Mo bá fun yín nínú Tírà àti ìjìnlẹ̀ òye (ìyẹn, sunnah ẹnì kọ̀ọ̀kan wọn). Lẹ́yìn náà, Òjíṣẹ́ kan (ìyẹn, Ànábì Muhammad s.a.w.) yóò dé ba yín; ó máa fi èyí t'ó jẹ́ òdodo rinlẹ̀ nípa èyí t'ó wà pẹ̀lú yín. Nítorí náà, ẹ gbọ́dọ̀ gbà á gbọ́, ẹ sì gbọ́dọ̀ ràn án lọ́wọ́." (Allāhu) sọ pé: "Ǹjẹ́ ẹ gbà? Ṣé ẹ sì máa lo àdéhùn Mi yìí?" Wọ́n sọ pé: "A gbà." (Allāhu) sọ pé: "Nítorí náà, ẹ jẹ́rìí sí (àdéhùn náà). Èmi ń bẹ pẹ̀lú yín nínú àwọn Olùjẹ́rìí." Aal Im'raan/81

## 41. Dajudaju afojusun gbogbo iṣẹ ti o jẹ titi Ọlọhun ni pe: ki ẹsin ododo o mu ọmọnìyàn ga, yóò wa jẹ eru kan ti o mo ẹsin kanga fun Ọlọhun Ọba gbogbo agbanla-aye, yoo si tun tu u silẹ kuro ni jije ẹrú fun ọmọniyan tabi ohun elo tabi itankitan. Nitori naa, Ẹsin Isilaamu-gẹgẹ bi ìwọ naa ṣe ri i - kii se afọmọ awọn eeyan, ko si ki n gbe wọn tayọ ipo wọn, ko si ki n sọ wọn di oluwa ati olùjọsìn fun.

Dajudaju afojusun gbogbo ìránṣẹ́ ti o jẹ titi Ọlọhun ni pe: ki ẹsin ododo o mu ọmọnìyàn ga, yóò wa jẹ ẹru

kan ti o mọ ẹsin kanga fun Ọlọhun Ọba gbogbo agbanla-aye, yoo si tun tu u silẹ kuro ni jijẹ ẹru fun ọmọniyan tabi ohun elo tabi itankitan. Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«تَعِسَ عَبْدُ الدِّينَارِ وَالدِّرْهَمِ وَالقَطِيفَةِ وَالخَمِيصَةِ إِنْ أُعْطِيَ رَضِيَ وَإِنْ لَمْ يُعْطَ لَمْ يَرْضَ»

"Ẹru owo diinar ati owo dirham, ati aso qoteefah pelu aso khomiisọ ti parun, ti won ba fun un yoo yonu, ti won ko ba fun un ko nii yonu" Sohiihu ti Al-Bukhaar 6435 Nitori naa, ọmọniyan ti o pe ko nii jẹ ẹni ti yoo maa tẹriba fun nnkan kan ayaafi Alloohu. Owo ko si nii so o di ẹru tabi iyi tabi ipo tabi idile. O si n be ninu itan yii ohun ti yoo maa ṣe afihan fun oluka, nkan ti awon eeyan wa lori re siwaju riran ojise, ati bi won se di leyin re (riran ojise nişẹ).

Nigbati awọn Musulumi akọkọ ṣe Hijira lọ si ilu Abasha, ti ọba Abasha ni igba naa loun- An-Najaashi- si bi wọn leere, ti o si sọ fun wọn pe: "Ẹsin wo ni yii, ti o ṣe wipe ẹ yapa awọn ijọ yin ninu rẹ, ti ẹ ko si darapọ mọ ẹsin mi tabi ẹsin ọkan ninu awọn ijọ yii? Jahfar ọmọ Abi Toolib sọ fun un pe: Irẹ ọba! Awa jẹ ìjọ kan ti o jẹ alaimọkan, a maa n sin awọn òrìṣà, a si maa n jẹ okunbete, a maa n se awọn ibajẹ, a si tun maa n ja okun ẹbi, a si tun maa n ṣe aburu si alabagbe, alagbara inu wa maa n jẹ ọ̀lẹ. Ori iyen ni a si wa titi ti Ọlọhun fi ran Ojiṣẹ kan si wa laaarin wa, a mọ iran re, ati ododo rẹ, ati afọkàntán rẹ, ati kiko ara ro kuro nibi nnkan ti ko lẹtọọ. O wa pe wa lọ si ọdọ Ọlọhun ki a le mu Un ni ọkàn ṣoṣo, ki a si maa jọsin fun Un, ki a si tun bọra

kuro nibi nnkan ti awa ati awọn baba wa n jọsin fun ninu awọn nnkan ti o yatọ si I (Ọlọhun) ninu okuta, ati awọn òrìṣà. O si pa wa láṣẹ pẹlu imaa sọ ododo, ati imaa pe afunnsọ (Amanah), ati imaa da ẹbi pọ, ati imaa se daadaa si alabagbe, ati jijawọ kuro nibi awon nnkan eewọ ati tita awọn ẹ̀jẹ̀ silẹ, o si kọ fun wa kuro nibi awọn ibajẹ, ati oro eke ati imaa jẹ owo omo-orukan ati imaa pa iro agbere mo awọn obinrin ti won ko ara won ni ijanu. O si tun pa wa láṣẹ ki a maa sin Ọlọhun ni Oun nikan, ki a si ma mu nnkan kan mọ Oun ni orogun. O si tun pa wa láṣẹ pẹlu Irun kiki ati Zakah yiyọ ati Aawẹ gbigba. O sọ pe: o wa ka awọn àlámọ̀rí Ẹsin Isilaamu fun un". A si gba a ni ododo, a si ni igbagbọ pẹlu rẹ, a si tun tele e pẹlu nnkan ti o mu wa, a si tun sin Ọlọhun ni Oun nikan ti a ko si mu nnkan kan mọ Ọn ni orogun, a si ṣe nnkan ti o ṣe ni eewọ lewa lori ni eewọ, a si gba nnkan ti o ṣe lẹ́tọ̀ọ́ fun wa ni ẹ̀tọ́". Imam Ahmad lo gbe e jade (1740) pelu iyato die, ati Abu Naheem ninu tira re ((IL'YATUL AOLIYAA))(1/115) ni nnkan ti o se ni soki. Ẹsin Islaam - gẹ́gẹ́ bi iwọ naa ṣe ri i - kii ṣe afọmọ awọn eeyan, ko si ki n gbe wọn tayọ ipo wọn, ko si ki n sọ wọn di oluwa ati ẹni ti a maa jọsin fun. Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{قُلْ يَا أَهْلَ الْكِتَابِ تَعَالَوْا إِلَىٰ كَلِمَةٍ سَوَاءٍ بَيْنَنَا وَبَيْنَكُمْ أَلَّا نَعْبُدَ إِلَّا اللَّهَ وَلَا نُشْرِكَ بِهِ شَيْئًا وَلَا يَتَّخِذَ بَعْضُنَا بَعْضًا أَرْبَابًا مِّن دُونِ اللَّهِ ۚ فَإِن تَوَلَّوْا فَقُولُوا اشْهَدُوا بِأَنَّا مُسْلِمُونَ}

Sọ pé: "Ẹ̀yin ahlu-l-kitāb, ẹ wá síbi ọ̀rọ̀ kan t'ó dọ́gba láàárin àwa àti ẹ̀yin, pé a ò níí jọ́sìn fún ẹnì kan àfi Allāhu. A ò sì níí fi kiní kan wá akẹgbẹ́ fún Un. Àti

pé apá kan wa kò níí sọ apá kan di olúwa lẹ́yìn Allāhu." Tí wọ́n bá sì gbúnrí, ẹ sọ pé: "Ẹ jẹ́rìí pé dájúdájú mùsùlùmí ni àwa." Aal Im'raan/64 Ọlọhun ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَلَا يَأْمُرَكُمْ أَن تَتَّخِذُوا الْمَلَائِكَةَ وَالنَّبِيِّينَ أَرْبَابًا ۗ أَيَأْمُرُكُم بِالْكُفْرِ بَعْدَ إِذْ أَنتُم مُّسْلِمُونَ}

(Ànábì kan) kò sì níí pa yín ní àṣẹ pé kí ẹ sọ àwọn mọlāika àti àwọn Ànábì di olúwa. Ṣé ó máa pa yín ní àṣẹ ṣíṣe àìgbàgbọ́ lẹ́yìn tí ẹ ti jẹ́ mùsùlùmí ni? Suuratu Al-Imraan: 80 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«لاَ تُطْرُونِي كَمَا أَطْرَتْ النَّصَارَى ابْنَ مَرْيَمَ فَإِنَّمَا أَنَا عَبْدُهُ فَقُولُوا عَبْدُ اللَّهِ وَرَسُولُهُ»

"E maa ṣe yin mi ni ayinju gẹgẹ bii awọn Nasoorah ṣe yin Ọmọ Maryam ni ayinju, dajudaju emi jẹ ẹru Rẹ (Ọlọhun) ni mi; nitori naa ẹ sọ pe: Ẹrú Ọlọhun ati Ojise Re". Sọhiihu ti Buhari 3445

## Ọlọhun Ọba ṣe tituuba ni ofin, oun naa si ni: Pipada ọmọniyan si ọdọ Oluwa rẹ, ati gbigbe ẹṣẹ ju silẹ, ati pe Isilaamu maa n pa nnkan ti o ba ṣáájú rẹ rẹ ninu awon ẹṣẹ. Ati pe tituuba naa maa npa nkan ti o ba ti saaju re re ninu awon ẹṣẹ. Nitori naa, omoniyan o

**bukaata si ki o maa jẹwọ awọn àṣìṣe rẹ ni iwaju àwọn eeyan abara.**

Ọlọhun Ọba ṣe tituuba ni ofin, oun naa si ni: Pipada omoniyan si odo Oluwa re, ati gbigbe ese ju sile, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

{وَتُوبُوا إِلَى اللَّهِ جَمِيعًا أَيُّهَ الْمُؤْمِنُونَ لَعَلَّكُمْ تُفْلِحُونَ}

Kí gbogbo yín sì ronú pìwàdà sọ́dọ̀ Allāhu, ẹ̀yin onígbàgbọ́ òdodo nítorí kí ẹ lè jèrè. {suratul Nuur: 31.} Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{أَلَمْ يَعْلَمُوا أَنَّ اللَّهَ هُوَ يَقْبَلُ التَّوْبَةَ عَنْ عِبَادِهِ وَيَأْخُذُ الصَّدَقَاتِ وَأَنَّ اللَّهَ هُوَ التَّوَّابُ الرَّحِيمُ }

Ṣé wọn kò mọ̀ pé dájúdájú Allāhu Òun l'Ó ń gba ìronúpìwàdà lọ́wọ́ àwọn ẹrúsìn Rẹ̀, Ó sì ń gba àwọn ọrẹ, àti pé dájúdájú Allāhu, Òun ni Olùgba-ìronúpìwàdà, Àṣàkẹ́-ọ̀run?, Suuratut Taobah: 104. Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe:

{وَهُوَ الَّذِي يَقْبَلُ التَّوْبَةَ عَنْ عِبَادِهِ وَيَعْفُو عَنِ السَّيِّئَاتِ وَيَعْلَمُ مَا تَفْعَلُونَ }

Òun ni Ẹni t'Ó ń gba ìronúpìwàdà àwọn ẹrúsìn Rẹ̀. Ó ń ṣe àmójúkúrò níbi àwọn àṣìṣe. Ó sì mọ ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́. Suuratush Shuuroh: 25. Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- sọ pe:

«لَلَّهُ أَشَدُّ فَرَحًا بِتَوْبَةِ عَبْدِهِ الْمُؤْمِنِ مِنْ رَجُلٍ فِي أَرْضٍ دَوِّيَّةٍ مَهْلِكَةٍ مَعَهُ رَاحِلَتُهُ عَلَيْهَا طَعَامُهُ وَشَرَابُهُ فَنَامَ فَاسْتَيْقَظَ وَقَدْ ذَهَبَتْ فَطَلَبَهَا حَتَّى أَدْرَكَهُ الْعَطَشُ ثُمَّ قَالَ: أَرْجِعُ إِلَى مَكَانِيَ الَّذِي كُنْتُ فِيهِ فَأَنَامُ حَتَّى أَمُوتَ فَوَضَعَ رَأْسَهُ عَلَى سَاعِدِهِ لِيَمُوتَ فَاسْتَيْقَظَ وَعِنْدَهُ رَاحِلَتُهُ وَعَلَيْهَا زَادُهُ وَطَعَامُهُ وَشَرَابُهُ فَاللهُ أَشَدُّ فَرَحًا بِتَوْبَةِ الْعَبْدِ الْمُؤْمِنِ مِنْ هَذَا بِرَاحِلَتِهِ وَزَادِهِ»

Inu Ọlọhun maa n dun gidi gan an si tituuba (rironu piwada) ẹru Rẹ ti o je Mu'mini ju didunu arakunrin kan

lọ, ti arákùnrin naa wa ni inu asale ti o tun je aaye iparun, ti nnkan ọgun re si wa pelu re, ti jije ati mimu re naa tun wa lori re, ni o ba sun lo, o si taji pada, nnkan ogun re si ti lo, o wa bare si ni wa a titi ti òùngbẹ fi n gbe e. Lẹyin naa ni o wa so pe: Maa pada si aaye mi eleyi ti mo wa tele, maa wa sun titi ti maa fi ku, o wa gbe ori re le apa re ki o le ba ku, ni o ba taji, nnkan ọgun si ti wa ni odo re, ti ipese, jije ati mimu re si wa lori re. Inu Ọlọhun maa n dun gidi gan si tituuba (rironu piwada) eru Re ti o je Mu'mini ju bi inu eni yii se dun si riri ti o ri nkan ogun ati ipese re lo". Sohiihu Muslim: 2744

Ati pe Isilaamu maa n pa nnkan ti o ba ṣáájú rẹ rẹ ninu awọn ese. Ati pe tituuba naa maa n pa nnkan ti o ba ti ṣáájú re re ninu awọn ẹṣẹ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ قُل لِّلَّذِينَ كَفَرُوا إِن يَنتَهُوا يُغْفَرْ لَهُم مَّا قَدْ سَلَفَ وَإِن يَعُودُوا فَقَدْ مَضَتْ سُنَّتُ الْأَوَّلِينَ }

Sọ fún àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́ pé tí wọ́n bá jáwọ́ (nínú àìgbàgbọ́), A máa ṣàforíjìn ohun t'ó ti ré kọjá fún wọn. Tí wọ́n bá tún padà (síbẹ̀, àpèjúwe) ìparun àwọn ẹni àkọ́kọ́ kúkú ti ré kọjá (ní ìkìlọ̀ fún wọn). Suuratul Anfaal: 38. Ọlọhun si tun pe awọn Nasoorah si tituuba (rironu piwada), Ọba- ti ipo Rẹ gbọnngbọn sọ pe:

{ أَفَلَا يَتُوبُونَ إِلَى اللَّهِ وَيَسْتَغْفِرُونَهُ ۚ وَاللَّهُ غَفُورٌ رَّحِيمٌ }

Nítorí náà, ṣé wọn kò níí ronú pìwàdà sọ́dọ̀ Allāhu, kí wọ́n sì tọrọ àforíjìn lọ́dọ̀ Rẹ̀? Allāhu sì ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Suuratul Maaidah: 74. Ọlọhun si tun ṣe

gbogbo awọn oluyapa ati awọn ẹlẹṣẹ  ni ojukokoro si tituuba (rironu piwada), Ọba- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{قُلْ يَا عِبَادِيَ الَّذِينَ أَسْرَفُوا عَلَىٰ أَنفُسِهِمْ لَا تَقْنَطُوا مِن رَّحْمَةِ اللَّهِ ۚ إِنَّ اللَّهَ يَغْفِرُ الذُّنُوبَ جَمِيعًا ۚ إِنَّهُ هُوَ الْغَفُورُ الرَّحِيمُ}

Sọ pé: "Ẹ̀yin ẹrúsìn Mi, tí ẹ ti dẹ́ṣẹ̀ púpọ̀ sí ẹ̀mí ara yín lọ́rùn, ẹ má ṣe sọ̀rètí nù nípa ìkẹ́ Allāhu. Dájúdájú Allāhu l'Ó ń ṣàforíjìn gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ pátápátá. Dájúdájú Allāhu, Òun ni Aláforíjìn, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Suuratuz Zumar: 53. Nigbati Amru Bn Al-Aas pinu lati gba Isilaamu, o paya wipe wọn o ni fi ori àwọn ẹṣẹ rẹ ti o ti se ṣiwaju Isilaamu jin in. Amru so lẹniti o n gba egbawa nnkan ti o ṣẹlẹ̀ yii wa:

(لَمَّا أَلْقَى اللهُ عَزَّ وَجَلَّ فِي قَلْبِي الْإِسْلَامَ قَالَ: أَتَيْتُ النَّبِيَّ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ لِيُبَايِعَنِي فَبَسَطَ يَدَهُ إِلَيَّ فَقُلْتُ: لَا أُبَايِعُكَ يَا رَسُولَ اللهِ حَتَّى تَغْفِرَ لِي مَا تَقَدَّمَ مِنْ ذَنْبِي قَالَ: فَقَالَ لِي رَسُولُ اللهِ صَلَّى اللهُ عَلَيْهِ وَسَلَّمَ: يَا عَمْرُو أَمَا عَلِمْتَ أَنَّ الْهِجْرَةَ تَجُبُّ مَا قَبْلَهَا مِنَ الذُّنُوبِ يَا عَمْرُو أَمَا عَلِمْتَ أَنَّ الْإِسْلَامَ يَجُبُّ مَا كَانَ قَبْلَهُ مِنَ الذُّنُوبِ)

Nigbati Ọlọhun- Ọba Alagbara ti O gbọnngbọn- fi Isilaamu si mi ni ọkan, o sọ pe: Mo wa ba Anabi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- lati gbe àdéhùn fun un, nigba naa ni o wa tẹ ọwọ́ re si mi, mo wa so pe: Mi o ni se adehun fun ọ irẹ ojiṣẹ Ọlọhun titi ti wa fi fi ori ese mi ti o ti ṣáájú jin mi, o sọ pe: Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- wa sọ fun mi pe, irẹ Am'ru, se oo mọ wipe hijira maa n pa awọn ẹṣẹ ti o ṣáájú rẹ rẹ ni, irẹ Am'ru, se oo mọ wipe Isilaamu maa n pa awọn ẹṣẹ ti o ṣáájú rẹ rẹ ni?. Muslim lo gbe e jade (121) ni nkan ti o gun bi iru eleyii, ati Ahmad (17827) atipe gbolohun yii ti ẹ ni.

## 43- Nitori naa, ninu Ẹsin Isilaamu, asopọ laaarin ọmọniyan ati Ọlọhun maa n wa taara ni, nitori naa, oo bukaata si ẹni kankan lati jẹ alagata laaarin iwọ ati Ọlọhun. Ẹsin Isilaamu si tun wa kọ ki a sọ awọn abara di olùjọsìn fun Un tabi akẹgbẹ fun Olohun nibi jijẹ Oluwa Rẹ ati nibi lilẹtọọ si ijọsin Re.

Ninu Ẹsin Isilaamu, ọmọniyan ko bukaata si ki o maa jẹwọ awọn ẹṣẹ rẹ ni iwaju awọn eeyan, ati pe ninu ẹsin Isilaamu asopọ laaarin eeyan ati Ọlọhun maa n wa taara ni, nitori naa, oo bukaata si enikankan lati je alagata laaarin iwọ ati Ọlọhun, gẹgẹ bi o se rekọja ni ipinro (36). Dajudaju Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- pe gbogbo eeyan lọ sibi tituuba (rironu piwada) ati ṣiṣẹri pada si ọdọ Rẹ, Oun naa bakanna ni O tun kọ fun wọn kuro nibi ki wọn mu awọn Anabi tabi awọn Malaika ni alagata laaarin Rẹ ati awọn ẹru Rẹ. Nitori naa, Ọba- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ وَلَا يَأْمُرَكُمْ أَن تَتَّخِذُوا الْمَلَائِكَةَ وَالنَّبِيِّينَ أَرْبَابًا ۗ أَيَأْمُرُكُم بِالْكُفْرِ بَعْدَ إِذْ أَنتُم مُّسْلِمُونَ }

(Ànábì kan) kò sì níí pa yín ní àṣẹ pé kí ẹ sọ àwọn mọlāika àti àwọn Ànábì di olúwa. Ṣé ó máa pa yín ní àṣẹ ṣíṣe àìgbàgbọ́ lẹ́yìn tí ẹ ti jẹ́ mùsùlùmí ni? Suuratu Al-Imraan: 80 Esin Isilaamu- gẹgẹ bi o ṣe ri i- si tun

wa kọ ki a sọ awọn abara di olùjọsìn fun tabi akẹgbẹ fun Ọlọhun nibi jijẹ Oluwa Rẹ ati nibi lilẹtọọ si ijọsin Rẹ. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ nipa awọn Nasoorah pe:

{اتَّخَذُوا أَحْبَارَهُمْ وَرُهْبَانَهُمْ أَرْبَابًا مِّن دُونِ اللَّهِ وَالْمَسِيحَ ابْنَ مَرْيَمَ وَمَا أُمِرُوا إِلَّا لِيَعْبُدُوا إِلَٰهًا وَاحِدًا ۖ لَّا إِلَٰهَ إِلَّا هُوَ ۚ سُبْحَانَهُ عَمَّا يُشْرِكُونَ }

Wọ́n mú àwọn àlùfáà wọn (nínú yẹhudi) àti àwọn àlùfáà wọn (nínú nasara) ní olúwa lẹ́yìn Allāhu. (Wọ́n tún mú) Mọsīh ọmọ Mọryam (ní olúwa lẹ́yìn Allāhu). Bẹ́ẹ̀ sì ni A ò pa wọ́n láṣẹ kan tayọ jíjọ́sìn fún Ọlọ́hun, Ọ̀kan ṣoṣo. Kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Ó mọ́ tayọ ǹǹkan tí wọ́n ń fi ṣẹbọ sí I. Suuratut Taobah: 31. Ati pe Ọlọhun tako awọn alaigbagbọ latari wipe wọn mu awọn alagata laaarin wọn ati Oun (Alloohu). Nitori naa, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{أَلَا لِلَّهِ الدِّينُ الْخَالِصُ ۚ وَالَّذِينَ اتَّخَذُوا مِن دُونِهِ أَوْلِيَاءَ مَا نَعْبُدُهُمْ إِلَّا لِيُقَرِّبُونَا إِلَى اللَّهِ زُلْفَىٰ إِنَّ اللَّهَ يَحْكُمُ بَيْنَهُمْ فِي مَا هُمْ فِيهِ يَخْتَلِفُونَ ۗ إِنَّ اللَّهَ لَا يَهْدِي مَنْ هُوَ كَاذِبٌ كَفَّارٌ}

Gbọ́! Ti Allāhu ni ẹ̀sìn mímọ́. Àwọn tí wọ́n sì mú àwọn aláfẹ̀yìntì kan yàtọ̀ sí Allāhu, (wọ́n wí pé): "A ò jọ́sìn fún wọn bí kò ṣe pé nítorí kí wọ́n lè mú wa súnmọ́ Allāhu pẹ́kípẹ́kí ni." Dájúdájú Allāhu l’Ó máa dájọ́ láàárin wọn nípa ohun tí wọ́n ń yapa ẹnu nípa rẹ̀ (ìyẹn, ẹ̀sìn ’Islām). Dájúdájú Allāhu kì í fi ọ̀nà mọ ẹni tí ó jẹ́ òpùrọ́, aláìgbàgbọ́. Suuratuz Zumar: 3. Ọlọhun si tun ṣàlàyé wipe dajudaju awọn olooṣa- awọn alaimọkan- maa n mu awọn alagata laaarin wọn ati Ọlọhun, wọn wa maa n sọ pe: dajudaju awọn (alagata) maa n sun wọn mọ Ọlọhun.

Ati pe ti Ọlọhun ba kọ̀ fun awon eeyan kuro nibi ki won o mu awọn Anabi tabi awọn Malaika ni alagata laarin Re ati awon eru Re; nitori naa, eniti o yato si won (awon Anabi ati awon Malaaika) lo fi n leto ju láti ma ṣe mu ni alagata. Bawo wa ni, ti awon Anabi ati awon Ojiṣẹ- ki ọla Ọlọhun maa ba wọn- na si maa n tara sàsà láti sunmọ Ọlọhun. Ọlọhun ti ola Rẹ ga sọ ni Ẹni ti O n fun wa ni iro nipa isesi awon Anabi ati awon Ojise - ki ola Ọlọhun maa ba wọn- pe:

{إِنَّهُمْ كَانُوا يُسَارِعُونَ فِي الْخَيْرَاتِ وَيَدْعُونَنَا رَغَبًا وَرَهَبًا ۖ وَكَانُوا لَنَا خَاشِعِينَ }

Dájúdájú wọ́n ń yára gágá níbi àwọn iṣẹ́ rere. Wọ́n ń pè Wá pẹ̀lú ìrètí àti ìpáyà. Wọ́n sì jẹ́ olùtẹríba fún Wa. Suuratul Anbiyaah: 90. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga julọ-tun sọ pe:

{أُولَٰئِكَ الَّذِينَ يَدْعُونَ يَبْتَغُونَ إِلَىٰ رَبِّهِمُ الْوَسِيلَةَ أَيُّهُمْ أَقْرَبُ وَيَرْجُونَ رَحْمَتَهُ وَيَخَافُونَ عَذَابَهُ ۚ إِنَّ عَذَابَ رَبِّكَ كَانَ مَحْذُورًا}

Àwọn wọ̀nyẹn tí wọ́n ń pè (lẹ́yìn Rẹ̀) ń wá àtẹ̀gùn sọ́dọ̀ Olúwa wọn ni! - Èwo nínú wọn l'ó súnmọ́ (Allāhu) jùlọ (báyìí)? – Àwọn náà ń retí ìkẹ́ Allāhu, wọ́n sì ń páyà ìyà Rẹ̀. Dájúdájú ìyà Olúwa rẹ jẹ́ ohun tí wọ́n gbọ́dọ̀ ṣọ́ra fún. Suuratul Is'raah: 57. Iyẹn ni wipe: Dajudaju awọn ti ẹ n pe lẹyin Ọlọhun- ninu awọn anabi ati awọn ẹniire- awọn naa maa n sunmọ Ọlọhun, wọn si tun maa n rankan ikẹ Rẹ, wọn si tun maa n bẹru iya Rẹ; bawo wa ni wọn o ṣe maa pe wọn lẹyin Ọlọhun.

**Ni ipari tira yii, a maa ranti wipe awọn èèyàn, pẹ̀lú bi igba wọn ati awọn**

ẹyameya wọn ati awọn ilu wọn ati àwùjọ wọn ṣe yàtọ̀ síra, bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n ṣe yàtọ̀ síra níbi irori wọn àti erongba wọn, ti àyíká wọn àti iṣẹ́ wọn naa si tun yàtọ̀ síra, èyí ni o jẹ ki o jẹ dandan fun wọn láti ni afinimọna kan ti o maa tọ wọn sọna, ati eto kan ti yoo ko wọn jọ, ati adari kan ti yoo maa dáàbò bo wọn, awọn ojiṣẹ alapọn-ọnle- ki ikẹ ati ọla maa ba wọn- maa ṣe iyẹn pẹlu imisi lati ọdọ Ọlọhun, wọn maa n tọ àwọn eeyan s'ọna lọ si oju-ọna daadaa ati imọna, wọn si maa n ko wọn jọ si ori ofin Ọlọhun, wọn si tun maa n dajọ laaarin wọn pẹ̀lú ododo. Nitori naa, alamọri wọn yoo duro deede ni ibamu si jijẹ ipe wọn fun awọn ojiṣẹ yii, ati si sunmọ igba wọn si awọn ìránṣẹ́ ti Ọlọhun. Ọlọhun wa fi opin si awọn ìránṣẹ́ Rẹ pẹlu riran Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ni iṣẹ́, O si kọ àkọsílẹ̀ si ṣeku gbere fun un, O si tun ṣe e ni imọna fun awọn eeyan ati ikẹ

**ati imọlẹ ati itọsọna lọ si oju-ọna ti yoo muni de ọdọ Rẹ- mimo ni fun Un-**

Ni ipari tira yii, a maa ranti wipe awon èèyàn, pẹ̀lú bi igba won ati awon eyameya won ati awon ilu won ati àwùjọ wọn ṣe yàtọ̀ síra, bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n ṣe yàtọ̀ síra níbi irori wọn àti erongba wọn, ti àyíká wọn àti iṣẹ́ wọn naa si tun yàtọ̀ síra, èyí ni o jẹ ki o jẹ dandan fun wọn láti ni afinimọna kan ti o maa tọ wọn sọna, ati eto kan ti yoo ko wọn jọ, ati adari kan ti yoo maa dáàbò bo wọn, awon ojise alaponle - ki ike ati ola maa ba won - maa n se iyen pelu imisi lati odo Olohun, won maa n to awon eeyan s’ona losi oju-ona daadaa ati imona, won si maa n ko won jo si ori ofin Olohun, won si tun maa n dajo laarin won pẹ̀lú ododo. Nitori naa, alamori wọn yoo duro deede ni ibamu si jije ipe won fun awon ojise yii, ati sisunmo igba won si awon iranse ti Olohun. Nigba ti anu ti wa po, ti aimokan si ti kari, ti won si ti josin fun awon orisa; Olohun gbe anabi Re Muhammad - ki ike ati ola Olohun maa ba a - dide pelu imona ati esin ododo lati mu awon eeyan kuro nibi awon okunkun ṣíṣe Kèfèrí, aimokan, ati iborisa, lọ si ibi igbagbo ati imona.

**Fun idi eyii, mo n pe ọ, ìwọ omoniyan, ki o duro fun Ọlọhun ni iduro ododo eleyi ti yoo bọra kuro nibi àṣà ati ìṣe, ki o si tun lọ mọ wipe waa pada si ọdọ Oluwa rẹ lẹyin iku rẹ, ki o si tun woye**

**si ara rẹ ati awọn agbegbe ti o wa ni ayika rẹ. Nitori naa, gba Isilaamu, ki o le ba ṣe oriire ni aye re ati ọrun rẹ. Ti o ba wa fẹ wọ inu Isilaamu, ko si nnkan kan ti o jẹ dandan fún un ju ki o jẹrii wipe ko si ẹni ti ijọsin tọ si ni ododo ayaafi Alloohu, ati pe dajudaju Muhammad ojiṣẹ Rẹ ni, ki o si tun bọpa bọse kuro nibi gbogbo nnkan ti wọn ba n jọsin fun yàtọ̀ si Ọba Alloohu, waa tun ni igbagbọ wipe dajudaju Ọlọhun yoo gbe awọn ti wọn wa ninu saare dide, ati pe dajudaju ìṣirò ati ẹsan ododo ni, ti o ba ti wa jẹ́rìí pẹlu ijẹrii yii, o ti di Musulumi. O wa jẹ dandan fun o lẹyin iyẹn ki o maa jọsin fun Ọlọhun pẹlu nnkan ti O ṣe ni ofin bii Irun, ati zakah, ati Aawẹ, ati Hajj ti o ba ni ikapa ọna ati lo.**

Fun idi eyii, mo n pe o iwo omoniyan ki o duro fun Olohun ni iduro ododo eleyi ti yoo bora kuro nibi àṣà ati ìṣe, gẹgẹ bi Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ṣe pe ọ ninu gbolohun Re:

{قُلْ إِنَّمَا أَعِظُكُم بِوَاحِدَةٍ ۖ أَن تَقُومُوا لِلَّهِ مَثْنَىٰ وَفُرَادَىٰ ثُمَّ تَتَفَكَّرُوا ۚ مَا بِصَاحِبِكُم مِّن جِنَّةٍ ۚ إِنْ هُوَ إِلَّا نَذِيرٌ لَّكُم بَيْنَ يَدَيْ عَذَابٍ شَدِيدٍ}

Sọ pé: "Ohun kan ṣoṣo ni mò ń ṣe wáàsí rẹ̀ fun yín pé, ẹ dúró nítorí ti Allāhu ní méjì àti ní ẹyọ kọ̀ọ̀kan. Lẹ́yìn náà, kí ẹ ronú jinlẹ̀. Kò sí àlùjànnú kan lára ẹni yín. Kò sì jẹ́ kiní kan bí kò ṣe olùkìlọ̀ fun yín ṣíwájú ìyà líle kan." Suuratu Saba': 46. ki o si tun lọ mọ wipe dajudaju irẹ o pada si ọdọ Oluwa rẹ lẹyin iku rẹ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ- ga sọ pe:

{وَأَن لَّيْسَ لِلْإِنسَانِ إِلَّا مَا سَعَىٰ (39) وَأَنَّ سَعْيَهُ سَوْفَ يُرَىٰ (40) ثُمَّ يُجْزَاهُ الْجَزَاءَ الْأَوْفَىٰ (41) وَأَنَّ إِلَىٰ رَبِّكَ الْمُنتَهَىٰ (42) }

Àti pé kò sí kiní kan fún ènìyàn àfi ohun t'ó ṣe níṣẹ́.

Àti pé dájúdájú iṣẹ́ rẹ̀, láìpẹ́ wọ́n máa fi hàn án.

Lẹ́yìn náà, wọ́n máa san án ní ẹ̀san rẹ̀, ní ẹ̀san t'ó kún jùlọ.

Àti pé dájúdájú ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ ni òpin (ìrìn-àjò ẹ̀dá). Suuratun Najm: 39-42. ki o si tun woye si ẹ̀mí mímọ́ rẹ ati awọn agbegbe ti o wa ni ayika rẹ. Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ أَوَلَمْ يَنظُرُوا فِي مَلَكُوتِ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضِ وَمَا خَلَقَ اللَّهُ مِن شَيْءٍ وَأَنْ عَسَىٰ أَن يَكُونَ قَدِ اقْتَرَبَ أَجَلُهُمْ ۖ فَبِأَيِّ حَدِيثٍ بَعْدَهُ يُؤْمِنُونَ}

Ṣé wọn kò wo ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ pẹ̀lú gbogbo ǹǹkan tí Allāhu dá? Àmọ́ sá ó lè jẹ́ pé Àkókò ikú wọn ti súnmọ́. Nígbà náà, ọ̀rọ̀ wo ni wọn yóò gbàgbọ́ lẹ́yìn rẹ̀? Suuratul Ah'roof: 185.

Gba Isilaamu ki o le ba ṣe oriire ni aye rẹ ati ọrun rẹ. Ti o ba wa fẹ wọ inu Isilaamu, ko si nnkan kan ti o jẹ dandan fun ọ ju ki o jẹrii wipe ko si ẹni ti ijọsin tọ si ni ododo ayaafi Alloohu, ati pe dajudaju Muhammad

ojiṣẹ Rẹ ni. Nígbà ti Ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ran Muadh lọ si Yemen ni ẹni ti n pepe lọ si inu Ẹsin Isilaamu, o sọ fun un pe:

«إِنَّكَ تَأْتِي قَوْمًا مِنْ أَهْلِ الْكِتَابِ فَادْعُهُمْ إِلَى شَهَادَةِ أَنَّ لَا إِلَهَ إِلَّا اللهُ وَأَنِّي رَسُولُ اللهِ فَإِنْ هُمْ أَطَاعُوا لِذَلِكَ فَأَعْلِمْهُمْ أَنَّ اللهَ افْتَرَضَ عَلَيْهِمْ خَمْسَ صَلَوَاتٍ فِي كُلِّ يَوْمٍ وَلَيْلَةٍ فَإِنْ هُمْ أَطَاعُوا لِذَلِكَ فَأَعْلِمْهُمْ أَنَّ اللهَ افْتَرَضَ عَلَيْهِمْ صَدَقَةً تُؤْخَذُ مِنْ أَغْنِيَائِهِمْ فَتُرَدُّ فِي فُقَرَائِهِمْ فَإِنْ هُمْ أَطَاعُوا لِذَلِكَ فَإِيَّاكَ وَكَرَائِمَ أَمْوَالِهِمْ»

"Dadadaju ire o lo ba ijo kan ninu awon ti won fun ni tira, yaa pe won lo si ibi jijeri wipe ko eniti ijosin to si ni ododo ayaafi Olohun Alloohu ati wipe dajudaju emi o ojise Olohun ni mi, ti won ba ti wa tele o nibi iyen, wa fi mo won wipe dajudaju Olohun ti se irun wakati maarun ni oranyan le won lori ni gbogbo ojo ati oru, ti won ba tun tele o nibi iyen, wa fi mo won wipe dajudaju Olohun ti se zakah ni oranyan le won lori, won o maa gba a lati odo awon abọrọ won, won o si maa da a pada fun awon olosi won, ti won ba tun tele e nibi iyen, wa sora kuro nibi imaa gba awon eyi ti o dara julo ninu awon dukia wọn". Sohiihu Muslim: 19 ki o si tun bọpa bọse kuro nibi gbogbo nnkan wọn ba n jọsin fun yàtọ̀ si Ọba Alloohu. Iwa ibọpa-bọsẹ kuro nibi nnkan ti wọn n jọsin fun yàtọ̀ si Ọlọhun Alloohu naa ni AL-HANEEFIYYAH tii se ìlànà Anabi Ibroohim- ki ọla Ọlọhun maa ba a- Ọlọhun ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ قَدْ كَانَتْ لَكُمْ أُسْوَةٌ حَسَنَةٌ فِي إِبْرَاهِيمَ وَالَّذِينَ مَعَهُ إِذْ قَالُوا لِقَوْمِهِمْ إِنَّا بُرَآءُ مِنكُمْ وَمِمَّا تَعْبُدُونَ مِن دُونِ اللَّهِ كَفَرْنَا بِكُمْ وَبَدَا بَيْنَنَا وَبَيْنَكُمُ الْعَدَاوَةُ وَالْبَغْضَاءُ أَبَدًا حَتَّىٰ تُؤْمِنُوا بِاللَّهِ وَحْدَهُ }

Dájúdájú àwòkọ̀ṣe rere ti wà fun yín ní ara (Ànábì) ’Ibrọ̄hīm àti àwọn t’ó wà pẹ̀lú rẹ̀. Nígbà tí wọ́n sọ fún ìjọ wọn pé: "Dájúdájú àwa yọwọ́-yọsẹ̀ kúrò nínú ọ̀rọ̀ yín àti ohun tí ẹ̀ ń jọ́sìn fún lẹ́yìn Allāhu. A takò yín. Ọ̀tá àti ìkórira sì ti hàn láààrin wa títí láéláé àyàfi ìgbà tí ẹ bá tó gbàgbọ́ nínú Allāhu nìkan ṣoṣo. Suuratul Mumtahana: 4. Waa si tun ni igbagbọ wipe dajudaju Ọlọhun yoo gbe awọn ti wọn wa ninu saare dide, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{ذَٰلِكَ بِأَنَّ اللَّهَ هُوَ الْحَقُّ وَأَنَّهُ يُحْيِي الْمَوْتَىٰ وَأَنَّهُ عَلَىٰ كُلِّ شَيْءٍ قَدِيرٌ (6) وَأَنَّ السَّاعَةَ آتِيَةٌ لَّا رَيْبَ فِيهَا وَأَنَّ اللَّهَ يَبْعَثُ مَن فِي الْقُبُورِ (7) }

Ìyẹn nítorí pé dájúdájú Allāhu, Òun ni Òdodo. Dájúdájú Òun l’Ó ń sọ àwọn òkú di alàààyè. Dájúdájú Òun sì ni Alágbára lórí gbogbo n̄ǹkan.

Àti pé dájúdájú Àkókò náà ń bọ̀. Kò sí iyèméjì nínú rẹ̀. Dájúdájú Allāhu yóò gbé àwọn t’ó ń bẹ nínú sàréè dìde. Suuratul Hajj: 6-7. Ati pe dajudaju ìṣirò ati ẹsan ododo ni, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe:

{وَخَلَقَ اللَّهُ السَّمَاوَاتِ وَالْأَرْضَ بِالْحَقِّ وَلِتُجْزَىٰ كُلُّ نَفْسٍ بِمَا كَسَبَتْ وَهُمْ لَا يُظْلَمُونَ }

Allāhu ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ pẹ̀lú òdodo àti nítorí kí Á lè san ẹ̀mí kọ̀ọ̀kan ní ẹ̀san n̄ǹkan tí ó ṣe níṣẹ́. A ò sì níí ṣe àbòsí sí wọn. Suuratul Jaathiyah: 22.

Ti o ba ti wa jẹ́rìí pelu ijeri yii, o ti di Musulumi. O wa je dandan fun o leyin iyen ki o maa josin fun Olohun pelu nkan ti O se ni ofin bii Irun, ati Zakah, ati Aawe, ati Hajj ti o ba ni ikapa ona ati lo, ati nkan ti o yato si iyen.

Ẹda kan nìyí pẹlu déètì 19-11-1441

Ọjọgbọn Muhammad ọmọ Abdullaah As-Suhaym ni o kọ o.

Olùkọ́ imọ Aqeedah (adisọkan) ni ipin awọn ẹkọ ti o jẹ mọ ti Islaam (tẹlẹ ri).

Kulliyyah Terbiyah ni ilé-ẹ̀kọ́ giga Al-Malik Suhuud.

Ilu Riyadh, ni orílẹ̀-èdè Saudi Arabia

# Index

Ẹsin Isilaamu ........................................................... 2

Eleyii ni akọsilẹ soki kan nipa ẹsin Isilaamu gẹgẹ bi o ṣe wa ninu Alikuraani alapọnle pẹlu Sunnah Anọbi.................... 2

1. Ẹsin Isilaamu ni iṣẹ naa ti Allah fi ranṣẹ si gbogbo eniyan. Paapaajulọ Oun ni iṣẹ ayeraye ti o sijẹ opin awọn iransẹ Oluwa Allah............................................................. 2

2. Ẹsin Isilaamu kii ṣe ẹsin adayanri fun awọn ẹya tabi awọn ijọ kan pato. Ṣugbọn O jẹẹsin Allah fun gbogbo eniyan patapata.................................................................. 3

3. Isilaamu ni ifiranṣẹ Allah, eyi ti O wa lati pe awọn iṣẹ awọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ to ti kọja, eyi ti O fi ran wọn si awọn ijọ wọn, ki ikẹ ati ola Allah maa ba awọn ojiṣẹ Ọlọhun wọnyii. ................................................................. 5

4. Gbogbo awọn Anọbi patapata- ki ikẹ ati aanu Allah maa ba wọn- ẹsin kan ṣoṣo ni ẹsin wọn, bo tilẹ jẹ pe ilana iṣẹsin wọn ya lọtọọtọ. ......................................................... 6

5. Gẹgẹ bi gbogbo awọn Anọbi: Nuha, Ibrahim, Musa, Sulayman ati Dawuda ṣe pepe, bẹẹ naa ni Isilaamu ṣe pepe si inigbagbọ pe ẹni to njẹ Oluwa ni Allah, Aṣẹda, Olufunilarisiki, Ayeni, Apani, Ọlọla-gongo, Oun naa nii Oludari gbogbo nkan, Oun nikan yii naa ni Alaanu, Onikẹ to ga julọ. ............................................................... 8

Gẹgẹ bi gbogbo awọn Anọbi: Nuha, Ibrahim, Musa, Sulayman ati Dawuda ṣe pepe, bẹẹ naa ni Isilaamu ṣe pepe si ninigbagbọ pe ẹni to njẹ Oluwa ni Allah, Aṣẹda, Olufunilarisiki, Ayeni, Apani, Ọlọla-gongo, Oun naa nii Oludari gbogbo nkan, Oun nikan yii naa ni Alaanu, Onikẹ to ga julọ. Allah ti ọla Rẹ ga julọ sọ pe: ........................... 8

6. Ọlọhun Allah ti mimọ n bẹ fun-un ti ọla Rẹ sí ga julọ ni Aṣẹda, Oun naa ni O lẹtọ si ijọsin ni Oun nikan, ati wipe a o gbọdọ sin eyikeyi nnkan miran mọ Ọn. ...................... 14
7. Allah ni O da gbogbo nkan to n bẹ ninu Aye yala awọn nkan ti a ri tabi eyi ti a ko ri. Gbogbo nkan to ti yatọ si I (Allah) ni yoo maa jẹẹda kan ninu awọn ẹda Rẹ, O si da sanmọ ati ilẹ ni ijọ mẹfa: ............................................... 21
8. Allah ti mimọ ati giga ọla n bẹ fun-Un ko ni igbakeji yala nipa ọla tabi iṣẹda tabi idari tabi ijọsin bo tii wu ko mọ. . 22
9. Ati pe Alloohu Oba ti mimo n be fun Un, ko bi omo, won ko si bi I, ko si si akegbe ati alafijo Kankan fun Un. ....... 26
10. Ati pe Alloohu ti mimo n be fun Un ti ola Re si tun ga O ki n sokale si inu nkankan, ko si ki n di abara si inu nkankan ninu eda Re. ...................................................... 27
11. Alloohu ti mimo n be fun Un ti ola Re si tun ga je Aláàánú Onike si awon eru Re, fun idi eyi O ran awon ojise, O si tun so awon tira kale. ............................................... 30
12. Alloohu Oun ni Oluwa Onikẹ, Oun nikan ni Ẹni tí yóò ṣe iṣiro gbogbo ẹda ni ọjọ igbende nigba ti Yóò gbe gbogbo wọn dide lati inu saare wọn, ti Yíò sí san èèyàn kọọkan ní ẹsan pẹlu nkan ti o ba ṣe ninu dáadáa tàbí aidara, ẹnití o ba sì ṣe àwọn iṣẹ olóore ti o si jẹ Mu'mini, idẹkùn gbere n bẹ fún un, ati pe ẹnití o ba ṣe aigbagbo ti o si tun ṣe awọn iṣẹ aburu, iya ti o tobi n bẹ fún un ni ọjọ ìkẹhìn. .................. 31
13. Alloohu ti mimọ n bẹ fún Un ti ola Re Si tun ga da Anobi Ādam lati ara erupẹ, O wa je ki awon aromodomo re o maa po si leyin re. Nitori naa, awọn èèyàn patapata bákan náà ni won ni ipilẹ wọn, ko sì ọlá fún iran kan lori iran kan, ko sì tun sí fún ìjọ kan lori ijọ kan ayaafi pẹlu ìbẹrù ............... 35
14. Ati pe gbogbo ọmọ kọọkan ní won bi sí inú adamọ (Esin Islaam). ................................................................. 37

15. Ko sí ẹnikeni ninu awọn eeyan ti won bi ni ẹlẹsẹ, tabi eniti n jogun ẹsẹẹnití ọ yato sí i.: .................................... 39
16. Ati pe nǹkan ti a torí rẹ dá àwọn ènìyàn naa ni: Jijosin fún Olohun ni Oun nikan: ............................................... 41
17. Islam pon omoniyan le- ati okunrin ati obinrin- o si se agbateru fun un nibi gbogbo iwo re, o si se e ni ẹni tí won o bi leere nípa gbogbo awọn nkan ti o sesa re fúnra rẹ àti àwọn iṣẹ rẹ ati awọn ìwà rẹ, o si tun n dì ru u abajade eyikeyi iṣẹ ti o ba le fi ko inira ba ẹ̀mi ara rẹ tabi ti o le ko inira ba elomiiran. ............................................................................ 42
18. Islaam se okunrin ati obinrin ni deede ara wọn nibi iṣẹ ati ojuse ati ẹsan. ......................................................... 47
19. Islaam pọn obìnrin le, o si ka wọn kun pe bákan náà ni wọ́n ṣe ri pẹ̀lú awọn ọkunrin, o si ṣe inawo ni dandan lori ọkùnrin ti o ba ni ikapa, ìnáwó ọmọbìnrin jẹ dandan lori bàbá rẹ, ti ìyá si jẹ dandan lórí ọmọkùnrin rẹ tí ó bá ti bàlágà ti o si ni ikapa, ti ìyàwó si jẹ dandan lori ọkọ rẹ. ............. 49
20. Iku kii se titan gbere, ati pe iku a maa pa ara ati emi, iku emi si ni pipinya re kuro ni ara, leyin naa yoo pada si ara leyin igbedide ojo Alukiyaamọ, ati pe Emi o ni bo si ara miran leyin iku ko si nii pada sinu ara mii (akudaaya). ... 52
21. Islaam n pepe lo si ibi nini igbagbo pelu awon ipile igbagbo ti o tobi, awon naa ni nini igbagbo si Olohun ati awon Malaaika Rẹ, ati nini igbagbo si awon iwe Olohun gẹ́gẹ́ bíi Taoreeta ati Injiila ati Zabuura – siwaju ki won o to yi oro inu won pada – ati Alukurani, ati nini igbagbo si gbogbo awon Anabi ati awon Ojise- ki ola maa ba gbogbo won- ati ki a ni igbagbo si ẹni ti o kẹyin won, oun naa ni Muhammad Ojise Olohun, igbeyin awon Anabi ati awon Ojise, ati nini igbagbo si ojo ikẹyin, ki a si tun mo wipe kani

isemi ile-aye je opin ni; ere ponbele ni isemi ati bibẹ o ba jẹ, ati nini igbagbo si kadara ............................................ 54

22. Àti pé awon Anabi Olohun won ti so won kuro nibi sise asise – ki ola o maa ba won – nibi nkan ti won n mu de etigbo awon eeyan nipa Olohun, won si tun so won kuro nibi gbogbo nkan ti o ba ti tako laakaye tabi nkan ti iwa to dáa ba tako, ati pe awon Anabi Olohun won je eniti a ti la mimu awon ase Olohun de odo awon ẹrú Re bọ lọrun, ati pe awon Anabi Olohun ko si nkankan fun won ninu awon ìròyìn jijẹ oluwa tabi ẹni tí ó lẹ́tọ̀ọ́ si ìjọsìn; bi kii se pe abara ni won gegebi awon abara yoku ti Olohun si n mu imisi awon oro Re wa ba won.................................................. 71

23. Islam n pepe si ìjọsìn fun Olohun nìkan ṣoṣo pẹ̀lú àwọn ipilẹ ìjọsìn ńlá bii: IRUN ti o se pe oun naa ni diduro ati titẹ kọkọrọ ati fifi ori kanlẹ, ati iranti Ọlọhun ati yiyin-In ati adua, ọmọniyan yoo maa ki irun naa ni ẹẹmarun ni ojoojumọ, ko si si opinya kankan laarin awọn ti wọn n ki i, ati olówò ati talika, adarí ati ẹni tí wọ́n n dari, gbogbo wọn maa to ni saafu kan naa ninu irun. Bákan náà ni ZAKAT tii ṣe odiwọn kékeré ninu dukia ni ibamu si awọn májẹ̀mú ati ipebubu tí Ọlọhun ti pebubu rẹ, ti o jẹ dandan ninu dúkìá àwọn ọlọrọ, ti wọn maa yọ fun awọn alaini ati awọn mìíràn ni ẹẹkan ni ọdún. Bákan náà ni AAWẸ tí í ṣe kiko ẹnu ro nibi awọn nkan tii ba aawẹ jẹ ninu oṣu Ramadan, ni eyi ti o maa n re erongba ati sùúrù ninu ẹ̀mí. Bákan náà ni HAJJ tii ṣe lílọ si ilé Oluwa ni ilu Mẹka ni ẹẹkan ni ìgbésí ayé fun ẹni tí ó bá ni ikapa. Ninu Hajj yii, gbogbo èèyàn maa ri bákan náà nibi ìdojúkọỌlọhun Adẹda, ti ko si nii si pe ẹnikan wa ni ipò tí o ga ju ẹlòmíràn lọ ........................... 79

24- Lara àwọn nnkan ti o maa n jẹ ki ìjọsìn o da yàtọ̀ ju nínú Islam ni àwọn ọna ti a n gba ṣe e, àti àwọn àsìkò rẹ, àti àwọn

májẹ̀mú rẹ, Ọlọhun ṣe e ni òfin, O si mu u de ọdọ ojiṣẹ Rẹ, abara kankan ko si le e kun tabi din in ku titi di òní, gbogbo àwọn ìjọsìn ńlá ńlá yii ni gbogbo àwọn Anọbi naa pepe si, ki ọlà Ọlọhun lọ máa bá wọn. ........................................ 85

25. Ojiṣẹ ẹsin Isilaamu naa ni Muhammad ọmọ Abdullaah ti o wa nínú àwọn arọmọdọmọ Ismail ọmọ Ibrahim (ki ọlà Ọlọhun maa ba wọn). Wọn bi i si ìlú Mẹka ni ọdún 571 ti hijra, wọn gbe e dide ni ojiṣẹ nibẹ, o ṣi ṣe hijra lati ibẹ lọ sí ìlú Mẹdina. Ko ba àwọn ìjọ rẹ kópa nibi alaamọri oosa, ṣùgbọ́n ó máa ń ba wọn kópa nibi àwọn iṣẹ́ ti o gbọnngbọn. Ìwà rẹ dara ṣíwájú ki o to di ojiṣẹ ti àwọn ìjọ rẹ si maa n pe e ni olufọkantan. Ọlọhun gbe e dìde ni ojiṣẹ nigba ti o pe ọmọ ogoji ọdún, O si kun un lọ́wọ́ pẹ̀lú àwọn nkan ìyanu ńlá, eyi ti o tobi ju nínú rẹ naa ni Alukurani Alapọnle, oun si ni o tobi ju ninu awọn àmì àwọn Anọbi, oun naa ṣi ni àmì ti o n ṣẹku ninu awọn àmì àwọn Anọbi títí di òní. Nígbà tí Ọlọhun pe ẹsin fun un, ti ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- náà si jẹẹ bi o ṣe tọ ati bí ó ṣe yẹ, o kú ni ọmọọdún mẹta lé ni ọgọta, wọ́n sin in sí ìlú Mẹdina, oun si ni igbẹyin àwọn Anọbi ati awọn ojiṣẹ, Ọlọhun gbe e dìde pẹ̀lú imọna àti ẹsin òdodo, lati mu àwọn ènìyàn kúrò nínú òkùnkùn ibọrisa, aigbagbọ, ati aimọkan, lọ sibi imọlẹ imọỌlọhun lọkan ati ìgbàgbọ́, Ọlọhun si jẹri si i pe Oun ni Oun gbe e dìde láti maa pepe sibẹ pẹ̀lú iyọnda Rẹ. ........................................ 87

26. Sheria Islam ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mu wa naa ni òpin àwọn iṣẹ-riran ti Ọlọhun ati awọn òfin Rẹ, oun si ni òfin ti o pe ti dídára ẹsin ọmọniyan ati ayé rẹ n bẹ nibẹ, o si n sọ: Ẹsin àwọn èèyàn, ati ẹjẹ wọn, ati dúkìá wọn, ati làákàyè wọn, àti àwọn ọmọ wọn, o si ti pa gbogbo òfin ti o ṣíwájú rẹ rẹ, gẹ́gẹ́ bí àwọn òfin tí ó ṣíwájú naa ṣe pa ara wọn rẹ.......................................................... 93

27. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ko nii tẹ́wọ́ gba ẹsin kankan yàtọ̀ sí Islām ti Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- mu wa, ẹni tí ó bá gba ẹsin míràn yàtọ̀ sí Islām, wọn ko lee gba a lọ́wọ́ẹ lailai ........................................................ 96

28. Alukurani Alapọnle ni tira ti Ọlọhun fi ránṣẹ́ si Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- oun si ni ọrọ Olúwa gbogbo àgbáyé, Ọlọhun pe àwọn èèyàn ati alujannu nija lati mu irú rẹ wa, tabi suura kan nínú irú rẹ, ipenija naa ṣi n bẹ titi di òní. Alukurani si n fesi fun àwọn ìbéèrè pàtàkì ti o pọ ti o n ko idamudaabo ba ẹgbẹẹgbẹ̀rún ninu awọn èèyàn. Alukurani yii nkan ti a sọ ni titi di òní pẹ̀lú èdè Lárúbáwá ti o fi sọkalẹ, ti arafi kankan ko si dinku níbẹ̀, wọ́n tẹẹ jáde, wọ́n sì fọn ọn ka, tira nla ni tii ko agara ba ẹni tí ó bá fẹ́ mu irú rẹ wa, nǹkan ti o lẹ́tọ̀ọ́ si kíkà ni tabi kika ongbifọ àwọn ìtumọ̀ rẹ̀. Gẹ́gẹ́ bẹẹ naa ni ìlànà Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati ẹkọ rẹ ati ìtàn ìgbésí ayé rẹ, gbogbo ẹ ni wọ́n ṣọ tí wọ́n si gbe de ọdọ wa ni ibamu si sisẹntẹle latiọdọ àwọn ti wọn maa n gba ẹgbawa ti wọn ṣee fi ọkan tan. Wọn tẹ oun naa jáde pẹ̀lú èdè Lárúbáwá tii ṣe èdè Anọbi Muhammad (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a), wọn si túmọ̀ rẹ si ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn èdè. Alukurani ati Sunna ni ipilẹ kan ṣoṣo fun àwọn idajọ Islam ati awọn òfin rẹ. Wọn kii mu Islam latara ìwà àwọn ti wọn n pe apemọra rẹ, bi ko ṣe wipe wọn maa n mu u latara imisi ti Ọlọhun tii ṣe Alukurani ati Sunna. ...................... 98

29. Islam n pàṣẹṣíṣe dáadáa sí àwọn òbí méjèèjì kódà ki wọn ma jẹ Musulumi, o si tun pàṣẹṣíṣe dáadáa si awọn ọmọ náà pẹ̀lú. .................................................................... 104

30. Islām n pàṣẹ déédéé nibi ọ̀rọ̀ ati iṣẹ́ pẹ̀lú àwọn èèyàn títí tí ó fi dé orí àwọn ọ̀tá.................................................. 109

Islām n pàṣẹ ṣíṣe dáadáa si gbogbo ẹ̀dá pátá, o si n pèpè lọ síbi àwọn ìwà dáadáa àti àwọn iṣẹ́ rere.......................... 112
32. Islam n pàṣẹ ki a ní àwọn ìwà ẹlẹyìn bíi òdodo, ati pípé àmàánnà, ati ìkóraró nibi nkan ti ko dára, ati ìtìjú, ati ìgboyà, ati ninawo, ati títọrẹ, ati ríran ẹni tí ó ní bukaata lọ́wọ́, àti ríran ẹni tí ó wa nínú ibanujẹ lọ́wọ́, àti bíbọ́ẹni tí ebi ń pa, ati jíjẹ́ alamuleti rere, ati dida ẹbí pọ̀, ati ki káàánú àwọn ẹranko. ..................................................................... 115
Islam ṣe nnkan ti ó dára nínú nnkan jíjẹ ati nnkan mímu ní ẹ̀tọ́, o si tun pàṣẹ mimọ ọkàn àti ara àti ilé, torí ẹ ni o ṣe ṣe ìgbéyàwó ní ẹtọ gẹ́gẹ́ bí àwọn Anabi- ki ọlà máa bá wọn- ṣe pàṣẹ rẹ̀, gbogbo nnkan ti o dara ni wọn máa n pàṣẹ rẹ̀. . 122
Islām ṣe àwọn ipilẹ àwọn nkan ti a ṣe ni eewọ ni eewọ, gẹgẹ bii ẹbọ pẹ̀lú Ọlọhun, àti ṣíṣe Kèfèrí, ati sísin àwọn ooṣa, ati sisọ ohun ti èèyàn ò mọ̀ nípa Ọlọhun, àti pípa àwọn ọmọ, ati pípa ẹ̀mí ti a pọnle, àti ṣíṣe ibajẹ ni orílẹ̀, àti idán, ati ìwà ibajẹ ti o fi ojú hàn ati èyí tí ó pamọ, àti ṣìná, ati ki ọkùnrin maa ba ọkùnrin ẹgbẹ́ rẹ ni aṣepọ, o ṣe èlé ni eewọ àti jíjẹ okunbete, àti àwọn nkan ti wọn ba dú fún àwọn ooṣa, o ṣe ẹran ẹlẹ́dẹ̀ ni eewọ, àti àwọn ẹgbin ti o ṣẹ́kù, o ṣe jíjẹ dúkìá ọmọ orukan ni eewọ, ati didin òṣùwọ̀n kù, o ṣe jija okùn-ìbí ni eewọ. Àwọn Anọbi pátá- ki ọlà maa ba wọn- ni wọn fi ẹnu ko lori ṣíṣe àwọn nkan eewọ yii ni eewọ. ............... 124
Islām n kọ àwọn ìwà burúkú bii irọ́, irẹjẹ, ìjànbá, ẹtanjẹ, keeta, ète aburú, olè-jíjà, tẹnbẹlẹkun, ati àbòsí, Islam kọ gbogbo ìwà ti ko dára. .................................................... 131
Islām n kọ ibalopọ ti owó ti èlé ba wa ninu ẹ, tabi ìnira, tabi ẹtanjẹ, tabi àbòsí, tàbí irẹjẹ, tàbí nnkan ti o ba le ṣe okunfa inira ti o maa kárí àwùjọ ati awọn ọmọ ìlú ati ẹni kọọkan. ........................................................................................ 139

Islām wa lati wa da aabo bo làákàyè ati lati ṣe gbogbo nkan ti o ba le ba a jẹ ni eewọ gẹ́gẹ́ bí mímu ọtí, o pàtàkì làákàyè, o ṣe e ni okunfa lila nnkan bọni lọrun, o si la a kúrò nibi àjàgà itankitan ati ibọrisa. Ko si si awọn àṣírí ikọkọ kankan ninu Islām, bẹ́ẹ̀ si ni ko si awọn idajọ kankan ti o wa fun àwọn ipò kan nikan ti ko kan òmíràn, gbogbo àwọn ìdájọ́ rẹ ati òfin rẹ pátá ni o ba làákàyè ti o ni alaafia mu, o si wa ni ibamu si nnkan ti déédéé ati ọgbọn n tọka si. ................ 142

Àwọn ẹ̀sìn irọ, ti àwọn ti wọn n ṣe e ko ba ni agbọye àwọn àtakò ti o wa ninu ẹ, ati awọn nnkan ti o tako làákàyè, àwọn àlùfáà ẹ̀sìn naa yoo jẹ ki awọn olutẹle wọn lérò pe ẹsin ju làákàyè lọ ni, ati pe ko si igbalaaye fun làákàyè lati gbọ ẹsin ye. Àmọ́ Islām ka ẹsin kun imọlẹ ti o maa tan si ojú ọna fun làákàyè, ti àwọn ti wọn n ṣe ẹsin irọ n fẹ ki awọn èèyàn pa làákàyè ti ki wọn si maa tẹle àwọn, ti Islām si n fẹ ki ọmọniyan ta làákàyè rẹ ji lati mọ pàtó bi àwọn ọ̀rọ̀ ṣe jẹ́ gan. ........................................................................................ 146

Islam n babara imọ ti o ba ni alaafia, o si n ṣeni ni ojúkòkòrò lati maa ṣe iwadi ti imọ ti ko nii si ifẹ-inu ninu ẹ, o si tun n pepe si wiwoye ati rí ronú nipa ara wa ati nipa ayé ni àyíká wa, àwọn àbájáde ìwádìí ìmọ̀ ti o ba si ni àlàáfíà ko le tako Islam. ........................................................................... 148

40. Ati pe Ọlọhun ko nii gba iṣẹ, Ko si nii ṣe ẹsan le e lori ni ojo ikehin ayaafi ti o ba wa lati odo eniti o ni igbagbo pelu Olohun ti o si tun tele ase Re, ti o si tun gba awon ojise Re – ki ike ati ola maa ba won – ni ododo, ati pe Olohun ko nii gba ninu awon ijosin ayaafi èyí ti O ba se e lofin, nitori naa bawo wa ni omoniyan o se maa se aigbagbo pelu Olohun ti yoo wa maa reti ki o san an ni esan? Ati pe Olohun ko nii gba igbagbo enikeni ninu awon eeyan ayaafi ti o ba ni igbagbo si awon Anọbi- ki ola o maa ba gbogbo won

lapapo- ti o si tun ni igbagbo si jije ojise Muhammad (ki ike ati ola Olohun maa ba a)............................................... 152

41. Dajudaju afojusun gbogbo iṣẹ ti o jẹ titi Ọlọhun ni pe: ki ẹsin ododo o mu ọmọnìyàn ga, yóò wa jẹ eru kan ti o mo ẹsin kanga fun Ọlọhun Ọba gbogbo agbanla-aye, yoo si tun tu u silẹ kuro ni jije ẹrú fun ọmọniyan tabi ohun elo tabi itankitan. Nitori naa, Ẹsin Isilaamu- gẹgẹ bi ìwọ naa ṣe ri i - kii se afọmọ awọn eeyan, ko si ki n gbe wọn tayọ ipo wọn, ko si ki n sọ wọn di oluwa ati olùjọsìn fun. ................... 156

Ọlọhun Ọba ṣe tituuba ni ofin, oun naa si ni: Pipada ọmọniyan si ọdọ Oluwa rẹ, ati gbigbe ẹṣẹ ju silẹ, ati pe Isilaamu maa n pa nnkan ti o ba ṣáájú rẹ rẹ ninu awon ẹṣẹ. Ati pe tituuba naa maa npa nkan ti o ba ti saaju re re ninu awon ẹṣẹ. Nitori naa, omoniyan o bukaata si ki o maa jẹwọ awọn àṣìṣe rẹ ni iwaju àwọn eeyan abara. ..................... 159

43- Nitori naa, ninu Ẹsin Isilaamu, asopọ laaarin ọmọniyan ati Ọlọhun maa n wa taara ni, nitori naa, oo bukaata si ẹni kankan lati jẹ alagata laaarin iwọ ati Ọlọhun. Ẹsin Isilaamu si tun wa kọ ki a sọ awọn abara di olùjọsìn fun Un tabi akẹgbẹ fun Olohun nibi jijẹ Oluwa Rẹ ati nibi lilẹtọọ si ijọsin Re.............................................................. 163

Ni ipari tira yii, a maa ranti wipe awọn èèyàn, pẹ̀lú bi igba wọn ati awọn ẹyameya wọn ati awọn ilu wọn ati àwùjọ wọn ṣe yàtọ̀ síra, bẹ́ẹ̀ náà ni wọ́n ṣe yàtọ̀ síra níbi irori wọn àti erongba wọn, ti àyíká wọn àti iṣẹ́ wọn naa si tun yàtọ̀ síra, èyí ni o jẹ ki o jẹ dandan fun wọn láti ni afinimọna kan ti o maa tọ wọn sọna, ati eto kan ti yoo ko wọn jọ, ati adari kan ti yoo maa dáàbò bo wọn, awọn ojiṣẹ alapọn-ọnle- ki ikẹ ati ọla maa ba wọn- maa ṣe iyẹn pẹlu imisi lati ọdọ Ọlọhun, wọn maa n tọ àwọn eeyan s’ọna lọ si oju-ọna daadaa ati imọna, wọn si maa n ko wọn jọ si ori ofin Ọlọhun, wọn si

tun maa n dajọ laaarin wọn pẹ̀lú ododo. Nitori naa,  alamọri wọn yoo duro deede ni ibamu si jijẹ ipe wọn fun awọn ojiṣẹ yii, ati si sunmọ igba wọn si awọn ìránṣẹ́ ti Ọlọhun. Ọlọhun wa fi opin si awọn ìránṣẹ́ Rẹ pẹlu riran Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a- ni iṣẹ́, O si kọ àkọsílẹ̀ si ṣeku gbere fun un, O si tun ṣe e ni imọna fun awọn eeyan ati ikẹ ati imọlẹ ati itọsọna lọ si oju-ọna ti yoo muni de ọdọ Rẹ- mimo ni fun Un- ........................................................... 165

Fun idi eyii, mo n pe ọ, ìwọ omoniyan, ki o duro fun Ọlọhun ni iduro ododo eleyi ti yoo bọra kuro nibi àṣà ati ìṣe, ki o si tun lọ mọ wipe waa pada si ọdọ Oluwa rẹ lẹyin iku rẹ, ki o si tun woye si ara rẹ ati awọn agbegbe ti o wa ni ayika rẹ. Nitori naa, gba Isilaamu, ki o le ba ṣe oriire ni aye re ati ọrun rẹ. Ti o ba wa fẹ wọ inu Isilaamu, ko si nnkan kan ti o jẹ dandan fún un ju ki o jẹrii wipe ko si ẹni ti ijọsin tọ si ni ododo ayaafi Alloohu, ati pe dajudaju Muhammad ojiṣẹ Rẹ ni, ki o si tun bọpa bọse kuro nibi gbogbo nnkan ti wọn ba n jọsin fun yàtọ̀ si Ọba Alloohu, waa tun ni igbagbọ wipe dajudaju Ọlọhun yoo gbe awọn ti wọn wa ninu saare dide, ati pe dajudaju ìṣirò ati ẹsan ododo ni, ti o ba ti wa jẹ́rìí pẹlu ijẹrii yii, o ti di Musulumi. O wa jẹ dandan fun o lẹyin iyẹn ki o maa jọsin fun Ọlọhun pẹlu nnkan ti O ṣe ni ofin bii Irun, ati zakah, ati Aawẹ, ati Hajj ti o ba ni ikapa ọna ati lo. . 167